Ì Y Ì

# ÝÍÝÍ ÈTÒ
# ÌSÚNÁ RẸ PADÀ

## Agbára ti Inúrere

P Ò P

GARY KEESEE

A D À

Ọ̀rẹ́ mi ọ̀wọ́n nínú Krístì,

Àdúrà wa ni pé wà rí ìdánilẹ́kọ̣ yìí bí orísun ìbùkún àti ìgbani níyànjú fún ọ. Jọ̀wọ́ má tẹ̀tì làti pín ohun èlò yìí pẹ́lú àwọn ọ̀rẹ́ rẹ, ẹbí àti àwọn ọmọ ìjọ rẹ. Aha o le kàn sí FLNfree.com láti gba àgbàsílẹ̀ àwọn ẹ̀dá míràn tókù àti fún àwọn ìdánilẹ́kọ̣ ọ̀fẹ́ ní èdè abínibí rẹ.

Ọlọrun fẹ́ràn rẹ o sì ní àwọn ètò tí ó dàra fún ayé rẹ. Ẹ̀kọ́ tí a kọ́ nípa bí a ti nṣe nínú ìjọba Ọlọ́run yí ayé wa padà sí dídára, a sì gbàgbọ́ pé yóò ṣe ohun yi kanna fún ọ!

Pẹ́lú ìfẹ́ ti Krístì,

Garry ati Drenda Keese



P.S. Jọ̀wọ́ rántí láti lọ gba àgbàsílẹ̀ lọ́fẹ̀ẹ́ lórí ìtàkùn ayélujára wa FLNfree.com láti gba àgbàsílẹ̀ awọn tókù àti ìdánilẹ́kọ̣ lọ́fẹ̀ẹ́ ní èdè abínibí rẹ!

Ì Y Ì

# YÍYÍ ÈTÒ ÌSÚNÁ RẸ PADÀ

## Agbára ti Inúrere

P Ò P

GARY KEESEE

À D À

**Your Financial Revolution :**
***The Power of Generosity***, Yoruba. By Gary Keesee
Copyright © 2023 by Gary Keesee,

Originally published in English
ISBN: 978-1-945930-14-0

Gary Keese Ministries
P.O. Box 979, New Albany
OH 43054, USA
GaryKeesee.com

This book is a FREE GIFT from Gary Keesee Ministries and is NOT FOR SALE

**Yíyí Ètò Ìṣúná Rẹ Padà:**
***Agbára ti Inúrere,*** Yorùbá
Copyright © 2023 nipasẹ̀ Gary Keesee

Èdè Gẹ̀ẹ́sì ni akọ́kọ́ fi tẹ̀ ẹ́ jáde
ISBN: 978-9729035-9-2

Ilé -iṣẹ́ Ìrànsẹ́ Gary Keesee
P.O.Box  979,New Albany
OH 43054,USA
Garykeesee.com

Ẹ̀bùn ọ̀fẹ́ ní ìwé yìí láti ilé -iṣẹ́ Ìrànsẹ́ Gary Keesee  KÌÍ ÍSE FÚN TÍTÀ

# ÌYÀSỌ́TỌ̀

Mo fi ìwé yìí perí ìyàwó mi Drenda arẹwà obìnrin tí a ti jọ nbọ ní ogójì ọdún sẹ́yìn. Òun ni ẹnití mo mọ̀ tí ó jẹ́ onínúrere ènìyàn jùlọ tí mo ti bá pàdé. Gbogbo ìgbà ni o máa ńro ti àwọn ẹlòmíràn òn ni ó sì kọ́ mi ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ bi a ti se ń nífẹ àwọn ènìyàn, èyí ti màá ma dúpẹ́ títílaí fún!

—Gary Keesee

# ÀKÒÒNÚ ÌWÈ

**ÌFÁÀRÀ**..........................................................................09

**Orí 1:** Agbára ti Inúrere..........................................................15

**Orí 2:** Ìdáhùn: Ore–Ọ̀fé.............................................................29

**Orí 3:** Sé O Kójúòsùnwọ̀n?.......................................................53

**Orí 4:** Owo Tani O Je? ..............................................................67

**Orí 5:** O Nílò Alábasepọ̀...........................................................81

**Orí 6:** Àwọn Ohun Ìjìnlẹ̀ Ti Ìdáméwa..........................................93

**Orí 7:** O Nílò Àpamọ́wọ́: Apá Kínní.........................................109

**Orí 8:** O Nílò Àpamọ́wọ́: Apá Kejì.........................................133

**Orí 9:** Òfin Ti Osunwon............................................................143

**Orí 10:** Ọba Onínúrere ............................................................155

**Orí 11:** Ìlérí Fún Àwọn Tí Wọ́n Jẹ́ Onínúrere...............................171

# ÌFÁÀRÀ

Nígbàti Ọlọrun pe èmi àti Drenda lọ sórí tẹlifísiọnu, mo ní láti gbà bẹ́ẹ̀ torí ó jẹ́ nkan ti ó jìnnà gzn ní ẹ̀mí mi. Mo sẹ̀sẹ̀ padà ni láti Albania, ńibití mo ti lọ se ìdánilẹ́kọ́ ti oní igba máarún lórí ìjọba Ọlọrun àti sọ fún wọn bí èmi àti Drenda ti bọ́ kúrò nínú oko gbèsè nítorí tí a tẹlé àwọn òfin ìlànà ti ìjọba Ọlọrun.

Tí o bá ti ka àwọn ìwé tí a se sáájú, wàá sì rántí ìkùuku búlù tí ògo Ọlorun tí ó kún yàrá ìgbàlejò ti àwọn ajíhìnrere ní alẹ́ ọjọ́ tí a parí ìdánilẹ́kọ́ tó gbẹ̀yìn. Níbẹ̀ ni Olúwa ti bá mi sọ̀rọ̀, "*Mò ńpè ọ́ lọ sí gbogbo orílẹ̀-èdè láti lọ kọ́ àwon ènìyàn ní májẹ̀mú ti ètò ìsúná ti ìbùkún. Àti ìbikíbi tí mo bá rán ọ, ni èmi ó sanwó fún.*"

Ní alẹ́ ọjọ́ nà ni ayé mi yípadà. Bákanna, nkan tí Olúwa ní kí n se ninu ọ̀rọ̀ Rẹ̀ gan mí ò tí mọ̀ọ́ "*Mò ńpè ọ lọ sí orílẹ̀-èdè ayé gbogbo*"

Bí mo ti ń wòó, Ó dàbí pé orí telifísiọnù ni Olúwa ní lọ́kàn. Bákanna, kì íse ohun tí mo ní lọ́kàn láti se tàbí pẹ̀lú tí mo fẹ́ se. Ohun kan tí mo mọ̀ dájú nipé mo nifẹ́ sí láti máa ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́ láti sàwárí ohun tí èmi àti Drenda na ti rí—tí íse Ìjọba Ọlọrun.

Ọdún mẹ́sàn'án ni mo fi wà nínú gbèsè, tí mọ ǹgbé pẹlú orimsirisi àwọn nkan, tí ó mú mi máa jìjàkadì pẹlú àìlera àti ìbẹ̀rù. Àwọn ohun tí onísègùn òyìnbó fún mi kín lò láti dènà àìsàn dàbí ẹnipe kò se ràǹwọ́ kankan. Mo wá rí ara mi bí ẹnití ńkú lọ, tí ìbẹ̀ru wá gba gbogbo èrò mi. Ìbẹ̀rùbojo dé tí ó fi jẹ́ pé ẹ̀rù ńbà mí láti jáde nílé, tí ó sì hàn pé kò dára tó fún títa ọjà mi. Tí a sìtún ti súnmọ́ oko gbèsè, ó wá dàbí pé kò sí agbára mọ́ fún mi tí mo fi le dáwọ́ re dúró. À wá ńgbé ìgbem ayé ìtìjú, ó dàbí pé a ti ní ìjákulẹ̀. Èyí tí ó dùn mí júlọ ní tí ìyàwó mí arẹwà àti àwọn ọmọ mi. Ju gbogbo rẹ̀ lọ mi ò tún le pèsè owó tí wọn nílò fún wọn, Mo rí ara mí bí bàbá àti ọkọ tí kò pójú òsùnwọn tó ní ọdún nà.

À ńgbé nínú ahéré àtijọ́ tí 1850 níbití ohun gbogbo tí ó wà nínú rẹ̀ ti bàje tán. Okùn ni a fi so àwọn fèrèsé papọ̀. Gbogbo ení àtẹ́ká tí atẹ́ sílẹ̀ ni a rí ní ojú ọ̀nà sí ilé ìdọ̀tí. Ìbùsùn tí ó wà nínú yàrá àwọn ọmọkùnrin ni a rí ní ilé ilẹ̀. Awọn ọkọ̀ tí à ńwá tí gbó wọn tí ntìwá lójú. Nígbà gbogbo ni àwọn amòfin àti àwọn ilé isé ti àti jẹ nígbèsè ńpè wá.

Mí ò tílẹ̀ ní ìrètí mọ́! Bẹ́ẹ̀ni, Kristiani tí ó nífẹ́ Ọlọrun ni mí. Mò ńlọ sí

ṣọ́ọ̀ṣì mo sì tún gba ìrìbọmi ti Ẹ̀mí Mímọ́. Mo tún gba oyè nínú ìmọ̀ ẹ̀kọ́ Bíbélì ti ọlọ́dún kan nínú Májẹ̀mú Láíláí, síbẹ̀ àwọn nkan kò lọ dédé, àwọn ohun tí kò dára ńṣẹlẹ̀!

Ní ọjọ́ kan nínú ìbànújé, mo kígbe sí Ọlorun,à ní ẹsẹ̀kẹsẹ̀ ni o dámilóhùn. Kìí kúkú se pé mi ò gbàdúrà láarin ọdún mẹ́sán'án tí ó le koko náà; mo se bẹ́ẹ̀. Sùgbọ́n ní àsìkò yìí, mo *mọ̀* pé mo ní láti gbọ́ ohùn.

Mo léro pé títí ó fi di ìgbàna, mo máa ńronú pé mo le fa ara mi jáde kúrò nínú ipò àìní tí mo wà mo wá ńgbìyànjú láti se ohungbogbo pẹ̀lú agbára mi. Sùgbọ́n ní òwúrọ̀ ọjọ́ nà mo mọ̀ pé mo ti setán. Mo ti yá owó lọ́wọ́ gbogbo àwọn ọ̀rẹ́ tí mo ní, ẹgbẹgbẹ̀rún owó dọ́llà láti ọwọ́ àwọn ẹbí, gbogbo ọ̀nà tí mo le fi gbà yá owó ni ó ti dí.

Nígbàtí mo gbàdúrà ní òwúrọ̀ ọjọ́ nà, ipò àìníréti ni mo wà, síbẹ̀ ó wá yàmílẹ́nu pé ó tètè dámilóhùn ní kíákíá. Nínú ẹ̀mí mi mo gbọ́ tí ó sọ ẹsẹ Bíbélì yìí fún mi Filipi 4:19:

> *Sùgbọ́n Ọlọrun mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní yín, gegẹ́ bí orọ̀ rẹ̀ nínú ògo nínú Krístì Jésù.*

Mo wá sọ fún Olúwa padà pé, "Olúwa, mo mọ ẹsẹ Bíbélì yìí, sùgbọ́n mi ò ri kí o sẹlẹ̀ bẹ́ẹ̀ nínú ayé mi."Ó wá dámilóhùn padà pé ìdí tí o se rí bẹ̀ ni wípé mi ò ti kọ́ bí Ìjọba Rẹ̀ ti se ńsisé. Nkan tí ó sì sọ kò tí yé mi, sùgbọ́n èmi àti Drenda ti setán láti wádi ohun tí ó nsọ.

Ọ̀kan lára ẹsẹ Bíbélì tí Ọlọrun kọ́kọ́ fi hàn wá ni Lúkù 6:20:

> *"Nígbàtí ó sì gbé ojú rẹ̀ sókè sí àwọn ọmọ –ẹ̀hìn rẹ̀, ó ní:Alábùkún –fún ni ẹ̀yin òtòṣì nítorí ti yín ni ìjọba Ọlọrun."*

Ìjọba Ọlọrun ni ìdáhùn wa? Lẹ́ẹ̀kansi, a kò ti mọ ohun tí o sì nsọ nípa rẹ̀, sùgbọ́n a mọ̀ pé a ní láti lọ wádirè. A o sọ̀rọ̀ si nípa ìjọba láìpé, sùgbọ́n jẹ́ kí nsọ ohun tí èsì rẹ̀ jẹ. Ẹ̀mí Mímọ́ bẹ̀rẹ̀ sí ní fi àwọn nkan hàn wá láti inú Bíbélì tí a kò tí rí tẹ́lẹ̀. Bí a ti bẹ̀rẹ̀ sí se ohun tí Olúwa ńkọ́ wa nípa ìjọba, bẹ sì ni a jáde kúrò ní oko gbèsè pátápátá ní àrin ọdún méjì àti àbọ̀. A wá bẹ̀rẹ̀ sí ra ọkọ̀ wa pẹ̀lú owó lọ́wọ́ asì tún ra saarè ilẹ̀ ìwọ̀n

márùndínlọ́gọ́ta pẹ̀lú owó lọ́wọ́, ilẹ̀ tí ó kún fún àwọn ohun mèremère, igilíle àti ẹrẹ̀ ibití mo ti le sọdẹ ati le tọ́jú àwọn ọmọ mi ibi ìta gbansasa ńlá.

Ọ̀kan nínú ohun tí ó fún mi ní ayọ̀ ńlá ni tí mo rí Drenda tí o ńkọ́ ilé ìran rẹ̀, tí a kò tún jẹ gbèsè le lórí bákanna.

Lẹ́yìn ohun gbogbo tí mo ti là kọjá tí a sì ti rí ìjọba Ọlọrun tí ńsisẹ́ bí ó ti se nínú ayé wa, a wá ńgbé nínú ipò ayẹyẹ ní *ojojúmọ́.* Kódà a kò ti parim ayẹyẹ na. Awá sì tún ńse àjọyọ̀ ìjọba ni ojojúmọ́. Tí a ti kúrò nípò lílọ máa wá gbogbo ilé láti le rí owó tí a o fi ra ounjẹ tom dára fún àwọn ọmọ wa níbayí a ti bọ́ lọ́wọ́ gbèsè a ti le fi ẹgbẹgbèrún owó sílẹ̀ fún ìránlọ́wọ́ títànká ti ìhìnrere káàkiri àgbáyé ó pè fún àjọyọ̀.

Èmi àti Drenda ní ìfẹ́ sí síso fún àwọn ènìyàn nípa ìjọba Ọlọrun tó dára yìí. Torí ìdí yìí gan ni o mú mi lọ sí Albania. Gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ, nígbàtí Ọlọrun bam mi sọ̀rọ̀ ní Albania nípa lílọ sí àwọn orílẹ-èdè gbogbo, kò ye mi. Kínni èyí túmọ̀ sí? Ní àsìkò nà ni mo jẹ́ pásítọ̀ ìjọ kan tí èmi àti Drenda dá sílẹ̀ ní bí ọdún mẹ́wa sẹ́yìn. Sé màá kọ̀wé fi isẹ́ lẹ̀ ni màa wá bẹ̀rẹ̀ ìrìn àjò ni?

Nípasè àsẹ ìfihàn ti Ọlọrun ti yàn, èmi àti Drenda ni a fi hàn àwọn ènìyàn kan tí wọ́n ńse tẹlifisiọnù àti àwọn ilé isẹ́ tí ó sisẹ́ lórí ẹlifisiọnù. Kì íse pé mo ńwá wọn kiri: Ọlọrun kan mú wọn wá sí ipa ọ̀nà wa ni. Lẹ́èkansi kì íse pé mo ní ìfẹ́ sí sisẹ́ isẹ́ Tẹlifisiọnù rárá, sùgbọ́n mo rántí ìran kan tí mo rí bí ọdún díẹ̀ sẹ́yìn. Mo ńgbàdúrà nínú ìsìn wa kan lọ́jọ́kan, lójijì, ni Olúwa sọ fún mi pe ma lọ sí orí Tẹlifisiọnu àti rádio lọ sisẹ́. Mi ò tíì tilẹ̀ ròó tàbí fi sí ọkàn nítorí tí kò sí nínú àwọn ohun tí mo fẹ́ se ní àsìkò na, sùgbọ́n o rí bákan lára mi mo si sọ fún Drenda nipa rẹ̀.

Kí a má fa ọ̀rọ̀ gùn Ọlọrun sí àwọn ìlẹ̀kùn tí ó yanilẹ́nu sílẹ̀ fún wa ó sì tún mú àwọn ènìyàn wá sí ipa ọ̀nà wa lati rànwá lọ́wọ́ láti le se isẹ́ ti Telifisiọnù, síbẹ̀ a kò mọ ohunkóhun nípa Tẹlifisiọnù. *Nígbàtí mi ò bá sọ ohunkohun, kò sí nkankan.* Sùgbọn a rò wípé a ní láti máa tẹ̀lẹ́ohun tí Ọlọrun fi ńhàn wá. A kò ní irinsẹ́ kankan bẹ sì ni a kò mọ irú irinsẹ́ tí a nílò láti fi se isẹ́ nà, sùgbọ́n àwọn ènìyàn tí Ọlọrun mú wá fún wa mọ̀ ọ́n.

Lẹ́nukan a wá sí ibití a ti fẹ́ se ìpinnu. Ilé isẹ́ ti o Telifisiọnù kan bá wa dába àdéhùn láti má bá wọn sisẹ́. Tí wọ́n sì sírò gbogbo owó isẹ́ nà iye

àkókò lóri afẹ́fẹ́ àti iye tí gbogbo owó nà yóò ná wọn láti bẹ̀rẹ̀ ètò lórí Tẹlifisiọ̀nù àpapò rè yóò tó $300,000. Eyi si ni ọọdúnrún pọ́un ti a kò ní ní àsìkò na. Sùgbọ́n lẹ́yìn tí a ti gbàdúrà nípa rẹ̀ tí a sì wọ̀ yá ìjà pẹ̀lú Ọlọrun nípa rẹ̀, mo wá sọ pé bẹ́ẹ̀ni. (Lóòtọ́ o kò le bá Ọlọrun jà kí o borí).

Àwọn ilé isẹ́ nà wa sí ìlú (nítorí Texas ni ilé isẹ́ wọn wà), a sì bẹ̀rẹ̀ láti ya fiimù wa àkọ́kọ́ lórí ètò wa orí tẹlifisiọ́nù. Nígbàtí o sì jẹ́ wípé à wa kò ní irinsẹ́, Inú yàrá ìgbàlejò wa ni a ti ya gbogbo fiimù ọdún kan tí akọ́ko se. Ti mo bá sọ wípé ọkàn mi kò balẹ̀ rárá fún isẹ́ àkọ́kó tí a se àlàyé yen kò kún tó. Mi ò mọ ohun tí ó yẹ kí a máa retí. Kì ísì se pé a kan nse kíká ohùn sílẹ̀ lórí Tẹlifisọnù ni ó mú mi máa fokànbalẹ̀ o. Mo ní láti wà pẹ̀lú gbogbo ohun tí mo gbọ́dọ̀ lò lórí Tẹlifisiọ́nù láti le mú kí ètò nà dúró da, àti èmi ati Drenda ni a jọ nseé. Àwọn ẹgbẹ́ òsìsẹ́ nà fọwosowọ́pọ̀ pẹ̀lú wa wọn gbà wá nímọ̀ràn àti kọ́ wa, síbẹ̀ kò sí ìtẹ́lọ́rùn.

Jọ̀wọ́ mo fẹ́ kí o mọ̀ pé èmi kì íse ẹnití ó fẹ́ràn láti má jáde kiri, torínà fún mi láti wá má sètò lórí Tẹlifisiọnú ó jẹ́ pé mo ti kúrò níbi agbègbè ìtura mi. Bákanna, àwọn ẹgbẹ́ òsìsẹ́ ilé isẹ́ nà tún wá ba ọjọ́ tí a ńká ohùn sílẹ̀ na jẹ́. Olórí wọn ti lọ kúrò ní alẹ́ ọjọ́ nà nítorítí ọmọ rẹ̀ ọkùnrín kú lẹ́yìn tí ọkọ̀ alájọgbéle wọn gbá a lójú ọ̀nà. Òwúrọ̀ ni wọ́n sọ fún mi kí a tó bẹ̀rẹ̀ kíká ohùn sílẹ̀. Mo pinnu lati má sọ fún Drenda tití a fi setán. Wow, nkan tó le ni.

Lẹ́yìnna, tí a ká ohùn sílẹ̀ tán, ọ̀kan lára àwọn òsìsẹ́ wa lọ gbé kẹ̀kẹ́ ọmọ mi Tim ó sì lọ fi kọlu nkan.Tim sárem wọlé wá ó sunkún pé Dáfidì ti kú. Kòkú, o dákú ni, níbo lati fẹ́ bẹ̀rẹ̀ báyìí.

A la ọ̀sẹ̀ tí a ńká ohùn sílẹ̀ na kọjá, a sì bẹ̀rẹ̀ sí se àfihàn ètò na lórí afẹ́fẹ́ ní ibùdó ti agbègbè. A wá tẹ̀síwájú láti máa ká ohùn sílẹ̀ lẹ́kan lọ́sẹ̀ láàrin osù, sùgbọ́n nígbàtí osù kejì yóò fi parí, kò fẹ́ rọrùn mọ́; mo wá jìjàkadì pẹ̀lú pé ńkan kò se dédé mọ́ àti àyà jíjá ní gbogbo ìgbà bákannà. Mo wá kúkú sọ fún ẹnití o ni ilem isẹ́ nà pé mi ò ni le se èyí mọ́. Ó wò mí fún ìgbà díẹ̀ ó wá sọ pé, RÁRÁ! O ní láti má sé ÈTÒ na lọ!"

O wá sọ fún mi pé kín jókòó nítorí òun fẹ́ fi nkan hàn mí. Ó tan tẹlifisíọ̀nù ó sì gbe sí orí ìkànnì ti àwọn ètò Krìstíanì. Kámọparọ́, mi ò ti wo irú ètò Krìstíanì tó pọ̀ tó báyìí rí, sùgbọ́n ohun tí mo rí ní ọjo nà mú kí ara mi má da àti mú mi tún inú rò bí mo ti se ti lọ́wọ́ sí àti kópa pẹ̀lú

Tẹlifisiọnù fún ètò Krìstíanì .

Ọ̀kan nínú àwon ètò tí mo wọ̀, wọn ńta "òróró ólífì" tí wọ́n sọ pé ni yóò mú ìfàmìòróróyàn gidi wá. Ò míràn tún ni, oníwàásù ńta "bisikiti tí ati fòróróyàn" ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú tí o bá ti jẹ wà gba ìfihàn titun. Òmíràn tí mo tún wò ni mo gbọ́ tí o ní tí o ba ti se ìfifúnni láàrin ìsẹ́jú mẹ́ta, wa rí ìlópo mẹ́ta ìfòróróyàn láti serere. Tí ó túmọ̀ sí pé wọ́n fún wọn ní oúnjẹ tútù àti gbígbẹ. Gbogbo ohun tí wọ́n ńse wà dàbí pé wọn fún wọn ní ohun ẹ̀tàn kí ó ba le mú kí àwọn ènìyàn na se ìfifún ni.

Sùgbọ́n ohun kan tí mo sàkíyèsí ni pé kòsí ẹnikan nínú àwọn wọ̀nyìí tí o sọ fún wọn bí wọn ti se le rí nkan tí wọ́n nílò gbà—bi ìjọba Ọlọrun ti ńsisẹ́ gaan. Wọ́n ńsọ fún wọn láti fúnrúgbìn, sùgbọn mo mọ̀ pé ẹnikan ní lati sọ fún àwọn ènìyàn wọ̀nyìí bí wọn ti se le kó *ìkórè* ohun tí wọ́n fúnrúgbìn!

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun kekeke ti ìjìnlẹ ni àwọn ènìyàn wònyìí ní láti kọ́ tí wọ́n bá fẹ ní àseyọrí. Nípa kíkọ́ wọn bí wọn ti se le se ìfifúnni laí kọ́ wọn bí wọn ó ti se kórè, mo mọ pé inú àwọn ènìyàn yìí kò ní dùn sí Ọlọrun wọn ó lérò pé o ti já àwọn kulẹ̀ nígbàtí nkan kò bárí bí wọn ti ńreti kò ri ní ọ̀nà tí wọ́n ti fọkànsí.

Àwọn ènìyàn ní láti mọ ìlànà òfin ti ìjọba Ọlọrun àti ìdí tí ìfifúnni se se kókó nínú rírìn nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ti ìjọba Ọlọrun lórí ilẹ̀ ayé. Bákannà, ohun ti ó tún se pàtàkì júlọ ni pé, wọ́n ní láti mọ ohun tí ó yẹ kí wọ́n se *lẹ́yìn* tí wọn ti se ìfifún ni.Wọ́n nim láti mọ̀ bí a ti se ńkore ohun ti wọ́n bá nílò láti ọ̀dọ̀ Ọlọrun.

Mó wá ri pé èmi nà ní ipa tèmi láti kó nínú ìkórè tèmi—nkan àkọ́kọ́ ti mo ní lati kọ́ mọ̀ ni kínni ìgbàgbọ̀ jẹ ati kí ni ó dé tí a fi nílò rẹ̀. Mo ní lati ko bí Ẹ̀mí Mímọ́ yóò se darí mi sí ibi ìkórè mi ní àkókò àti bí ìkórè mi na yóò ti se lọ. Mo wa ri pé àwọn ìlànà òfin tẹ̀mí wà tí a ní látimọ̀ àti lò bákanna bí àwọn òfin ti wà tí ó nsàkóso ìpele ti ara tí yóò mú ìkórè wá.

Gbogbo àwọn ètò wọ̀nyìí rí bi pé kí owó sá ti máa wo inú àpótí meeli rẹ.

Mo fé gbà pé nígbà míràn *ọ́ rí bẹ̀* o wà nínú meeli rẹ, sùgbọ́n tí o bá gbé yẹwò dada, wa rí àmọ̀ràm tẹ̀mí bii Kílódé àti báwo ni om ti se dé bẹ̀.

Lẹ́yìn ìgbàtí mo ti wo díẹ̀ lára àwọn ètò yìí, Ojú gbàmìtì pẹ̀lú àwọn

ohun tí Mo rí. Abálájọ tí ayé kò se tẹ́tísí ohun tí à ńsọ mọ́. Sùgbon inúbími gan. Ní àsìkò yìí gan ni mo wá mọ̀ pé a nílò mi, pé mo ní nkan láti sọ.

Mo wá se ipinnu lati tẹ̀síwájú pẹ̀lú ètò orí Tẹlifisíọnù nítorí mo ní ìtàn láti sọ. Mo sì ti ńse ètò orí Tẹlifísọnù na láti ọdún mẹ́rìnlá sẹ́yìn báyìí mo wá ti rí tó ẹgbẹ̀gbẹrún àwọn èniyàn tó ti sàwárí ohnu tí à ńpè ní ìjọba Ọlọrun—kì íse ní ti ẹ̀sìn bíkòse ti ìjọba—wọ́n sì ní irú èsì kanna tí Èmi ati Drenda nà ni.

Mo mọ̀ pé ìwọ pẹ̀lú yóò ní èsì yí kannà.

Ìwé yìí, *Yíyí Ètò Ìsúná Rẹ Padà: Agbára Inúrere*, ni ẹlẹkarún àti ìwé èyí tí ó parí sísẹ̀ntẹ̀lẹ́ ìwem mi yim Yíyí Ètò Ìsúná Rẹ Padà. Inú mi dùn pé mo kọ àwọn ìwé nà parí, mo sì tún wá láyọ̀ lórí ìwé yi tí ó kẹ́yìn gbogbo ìwé nà.

—Gary Keesee

ORÍ KÍNNÍ

# ABGARA TI INURERE

Ní alẹ́ ọjọ́ kan èmi àti ìdílé mi lọ jẹ onjẹ alẹ́ nínú ilé oúnjẹ kan tí a féràn láti má lọ. ọ̀dọ́mọ̀bìnrin kan tí ó wà nínú oyún ni ó ńta oúnjẹ níbẹ̀. Bí mo ti fẹ láti san owó oúnjẹ tí a jẹ, lójijì mo mí ìmọ̀ ara láti bun ní owó tí ó pọ̀ díẹ̀ dípò ìpín mejìlélógún-mẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n tí mo má ńsan nígbogbo ìgbà, mo pinnu láti fi ọgọrun póùn kun owó nà láti fún un. Ó mú ìwé ìsanwó tí mo ti fọwọ́sí lọ lai yẹwò ó sì padà sí ilé ìdáná.

Láàrin ìṣẹ́jú kan ó padà wá, pẹ̀lú omijé ní ojú rẹ̀. Ó wá láti dúpẹ́ lọ́wọ́ wa. Ó sọ fún wa ipò àìní tó ó wà lọ́wọ́ báyìí àti bí ó ti se ńronú bí yóò ti se láàjá. Àwa lo ànfàní yìí láti pín ìhìnrere ti Krístid pẹ̀lú rẹ̀ àti gbàdúrà fún un kí á tó kúrò ní ibẹ̀. Akò se ohunkankan bíkòse inúrere láti sílẹ̀kùn àti sisẹ́ ìránsẹ́ fún ọkàn rẹ̀.

*Tàbí ìwọ ń gàn ọrọ̀ oore àti ìpamọ́ra àti sùúrù rẹ̀? Ìwọ kò ha mọ̀ pé oore Ọlọ́run ni ó ń fà ọ́ lọ sì* ***ìrònúpìwàdà?***

—Romu 2:4

Nínú Rómù 2:4 atúmọd ti Ọba Jákọ́bù sọ wi pé oore Ọlọ́run ni ó ń fà ọ́ lọ sì ìrònúpìwàdà.

**Bí ó bá jẹ́ oninúrere ò ńse bí Ọlọrun tí ńse ni.**

Mattiu 5:45 wípé:

*Kí ẹ̀yin lè jẹ́ ọmọ Baba yín ti ń bẹ ní ọ̀run. Ó mú kí oòrùn rẹ̀ ràn sára ènìyàn búburú àti ènìyàn rere, ó rọ̀jò fún àwọn olódodo àti fún àwọn aláìṣòdodo.*

Ọlọrun dára, ó sì jẹ oloóre! Àwa sì ni ọmọ rẹ̀, ìsẹ̀dá wa titun nínú Krístì jẹ́ ọ̀kan nínú kí a jẹ́ onínúre bákanna. Bí ó ti wà nínú ìtàn tí ó wà lókè, láti jẹ́ onínúre ní pínpín ọkàn Ọlọrún fún àwọn ènìyàn. Ó dà bí kí o má mu omi tútù ní ìgbà oru, jíjẹ́ onínumre mú ìtura àti ìretí wá sínú ayé tí ó wà nínú asálẹ̀ ti òsì.

Ipa ìfifúnni laífipáse hàn kedere nínú ohun tí Páùlù sọ nínú 2 Korinti 9:10-15, tí o kọ sí àwọn ìjọ kọ́rintì:

> *Ǹjẹ́ ẹni tí ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ, yóò fi irúgbìn fún un yín, yóò sì sọ ọ́ di púpọ̀, yóò sì mú èso òdodo yín bí sí i. Bẹ̀ẹ̀ ni a ó sọ yín di ọlọ́rọ̀ nínú ohun gbogbo, fún ìlawọ́ yín gbogbo tí ń ṣiṣẹ́ ọpẹ́ sí Ọlọ́run nípa wa.*
>
> *Nítorí iṣẹ́ ìránṣẹ́ ìsìn yìí kò kún ìwọ̀n àìní àwọn ènìyàn mímọ́ nìkan, ṣùgbọ́n ó túbọ̀ pọ̀ sí i nípa ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọpẹ́ sí Ọlọ́run. Nítorí ìdúró yin lábẹ́ ìdánwò iṣẹ́ ìsìn yìí, wọn yóò yin Ọlọ́run lógo fún ìgbọ́ràn yín ní gbígba ìhìnrere Kristi àti nípa ìlawọ́ ìdáwó yín fún wọn àti fún gbogbo ènìyàn. Àti nínú àdúrà fún un yín, ọkàn wọn ń se àfẹ́rí yín nítorí ọ̀pọ̀ oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ti ń bẹ nínú yín. Ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run nítorí aláìlèfẹnusọ ẹ̀bùn rẹ̀!*

Inúrere rẹ mú kí àwọn ènìyàn máa yin Ọlọrún àti dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ̀!!! Kíyèsí ohun tí Páùlù sọ pé jíjẹ́ onínúre jẹ́ *isẹ́ ìsìn* sí Ọlọrún ni.

Ìtumọ̀ isẹ́ ìsìn ni: *Isẹ́ tí ó ńse tàbí isẹ́ fún ẹni tógajùlọ tàbí bí ìránsẹ́.*[1]

Ara ojúse rẹ ni lórílẹ̀ ayé nítorí ti Ọlọrun, láti má pín ọkàn Rẹ adti àbójútó fún àwọn ènìyàn. Èsì rẹ hàn kedere—láti ní ìfọwọ́kàn ọkàn àwon ènidyàn àti sí payá láti gba Krístì. Mo lérò pé gbogbo wa ni ó le rántí ìgbàtí ẹnìkan tọ̀ wá wá àti bí ó ti tó nínú ọkàn wa.

Mo le rántí pe mo jẹ gbèsè egbẹ̀rún mẹ́rin pọ́ùn owó orí nígbàtí mo sẹ̀sẹ̀ gbéyàwó ti mi ò sì mọ̀ ọ̀ bí mo ti fẹ́ rí owó nà. Ọ̀pọ̀ òru ni mí o le sùn tí mò ńro inú ipò tí mo wà. TuIsa ni à ńgbé nígbànáà a sì sètò bí a ti fẹ́ lọ sàbẹ̀wò sí Ohio fún ìsinmi.

[1] *Ìwé Ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ ti èdè Gẹ̀ẹ́sì àtúnse kaàrún ti Améŕicám Heritagè.*

Nígbàtí bàbá mi bi mí leèrè pé báwo ni gbogbo nkan se ńlọ, mo sàlàyé fún wọn nípa owó IRS. Wọ́n sọ pe, "Ó da, ìyẹn rọrùn láti yanjú" wọ́n sì mú sọ̀wédowó wọn jáde wọ́n sì kọ iye owó tí mo jẹ na fún mi. Oore tí wọn se fún mi lẹsẹ̀kẹsẹ̀ mú ki ńtún nífẹ̀ẹ́ bàbá mi si ní àkókò náà ju bi mo ti fẹ́ràn wọn tẹ́lẹ̀ lọ. Nítorí ní àkókò yẹn, mo rí bí ọkàn wọn se rí símí.

Bàbá mi jẹ́ ẹni tí o máa fara pamọ́. Wọn kì ńfi nkan hàn sí gbangba fún ènìyàn. Kódà àti sí mọ̀mọ́ mi na. Bàbá mi kò tíì sọ fún mí rí pé àwọn fẹ́ràn mi láti ìgbàtí mo ti wà títí di àsìkò yìí, níwọ̀n bí mo ti se le rántí. Àfi ìgbàkan tí mọ̀mọ́ mi sọ fún wọn pé kí wọn sọ bẹ nà ni ìgbàkan tí wọn sọ ọ́, lẹ́yìn ọ̀pọ̀ dírámà. Mo sì nrántí ọjọ́ nà bí àná. Mọ̀mọ́ mi nbẹ̀bẹ̀ ni, pé, "O kò le sọ fún ọmọ rẹ pé o nífẹ rẹ̀?" Sùgbọ́n nísè ni ó dákẹ síbẹ̀.

Nípari , nígbàtí ó rí omijé lójú mọ̀mọ́ mi, wọn wá sọ pé àwọn nífẹ mi. Sùgbọ́n èmi kò ka àsìkò nà kún pé wọ́n nífẹ mi nítorí mo pe wọn mú wọn nítipá ni láti se bẹ́ẹ̀.

Dípò kí bàbá mi sọ́ lọ́rọ̀ fún wa pé àwọn fẹ́ràn wa, àwọn àkókò kan wà tí bàbá mi yóò lọ ra àwọn nkan tó se pàtàkì fún wa, mo sì rò wípé èyíí jẹ́ kí àwa ọmọ rẹ̀ mẹ́ẹrin mọ̀ pé bàba wa fẹ́ràn wa. Nípa nkan tí bàbá mi ńse ni mo ti ri ọkàn wọn pé wọ́n nífẹ wa,ó fẹ́ mà jẹ́ nípa ohun tí wọ́n bá sọ. Mo rí àwọn àsìkò na ọ̀rẹ́ mi ọ̀wọ́n bíi ìgbà tí ǹkan dá dúró bí ìmọ́lẹ̀ nínú òkùnkùn.

Ní ọjọ́ tí wọ́n kọ sọ̀wédowó fún mi torí gbèsè tí mo jẹ IRS, ọkàn mi kún fún ọpẹ́. Pẹlú omijé, mo dì mọ̀ bàbá mi mo sì dúpẹ lọ́wọ́ wọn. Ìdáhùn wọn jọmílójú gan. Wọ́n ní, "Níwọ̀n ìgbà tí mo níí lọ́wọ́, mo fẹ́ ràn ọ́ lọ́wọ́."

Mo mọ̀ pé ìwọ náà ńiran ẹnìkan tí ó ti se ọ́ lóore bí èmi na ti se, ní àkókò tí o wá sí ọ lókàn yìì. Torínà, ní àkíyèsí àti ìdí láti rántí:

**Inúrere máa fi ọkàn tìrẹ àti ọkàn ti Ọlọ́run fún wọn hàn ni.**

Inúrere lágbára gan ni. Ó tẹrí àwọn ọ̀rọ̀ ba ni àti lọ sínú ọkàn taàrà. Ó jẹ́ ohun tódára bí a ti se ńrántí ǹkan ìdùnnú tàbí ẹ̀bùn tí ẹnìkan fi fún wa.

Ìgbà àkọ́kọ́ tí mo sàkíyèsí ọkàn bàbá mi sì mi láyé ni ìgbàtí mo wà ní ìpele ẹ̀kọ́ kẹfà ní ilé ìwé. Èmi àti ọmọ ẹ̀gbọ́n mi kan ni a jọ fẹ́ seré

àwòkóse rọ́ọ̀kẹ́tì ní àsìkò náà, mo sì ti lọ ra ọ̀kan pẹ̀lú tí ó rí bí imú tí o le fi nkan bọ inú rẹ̀ kí o sì jú sí ojú ọ̀run.

Ní ọjọ́ tí à ńsọ yìí, èmi àti ọmọ ẹ̀gbọ́n mi ti lérò wípé a le fi ọ̀pọ̀lọ́ sínú kóónù yí kí a sì téépù koónù yí kí rọ́ọ̀kẹ́tì ba le forí sọ nkan dípò kí ó tú kí o sì fò lọ. Ìdí nipé a fẹ́ wo ohun tí yóò ṣẹlẹ̀ sí ọ̀pọ̀lọ́ nà, tí mo lérò pé ìwọ na le fojú inú wò.

Ó dáa, a ju rọ́ọ̀kẹ́tì na sókè, sí ǹkan àbùkù tí a se, bàbá mi na wà lójú òde láti wò wá. A sì mọ̀ pé inú wọn kò nídùn sí ọ̀pọ̀lọ̀ tí a pa.

Rọ́ọ̀kẹ́tì na lọ sókè bí ó ti yẹ ó sì túká ó sì tún padà sí lẹ̀. Bí mo ti lọ mú u padà, mo ri pé kóónù na ti fọ́nká tí ọ̀pọ̀lọ́ nà si ti kú, bí mo ti ńretim.

Bí mo ti mú róọ̀kẹ́tì na, mo tètè fi òkú ọ̀pọ̀ló nà sí ẹ̀gbẹ́kan kí bàbá mi má ba ri ǹkan tí a se. Ó sì wá bá wa wọ́n bèrè fún rọ́ọ̀kẹtì na. Mo sì tún rántí bí wọn ti se lọ́jọm nà nítorí rọọmkẹ́tì wa. Bí wọn ti gbà á sọ́wọ́, wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí ní sọ fún mi bí mo ti se le se, àti bí ó ti se dùn wọn pé ó bàjẹ́. Wọ́n wá se àlàyé mo ti se le tún rọ́ọ̀kẹ́tì tí ó ti túka se. Bí o ti ri gan ni ohùn wọn àti àánú wọn fún mi sí àsìse mi. Wọ́n kò ti ẹ̀ mọ̀ nípa ti ọ̀pọ̀lọ́, sùgbọ́n mi o le gbàgbem bim wọn ti se nítorí mi àti rọ́oḳẹ́tì mi ti ó bàjẹ́. Wọ́n dúró tì mí ní àkókò na wọ́n sì fi ìfẹ́ hàn sí mi.

Àwọn àkókò kan wà tí Ọlọ́run yóò lo àwọn ènìyàn tí a kò mọ̀ rí lati dúró tì wá àti gbà wá níyànjú.

Àkókò kan tí ó jẹ́ mamnigbàgbé ni àsìkò kan tí Èmi àti Drenda ti a sọdẹ ẹyẹ àparò lọ pẹ̀lú àwọn ọ̀rẹ wa kan. Èmi ati Drenda sì ṣẹ̀ṣẹ̀ se ìgbéyàwó ni a sì ńgbé ní Tulsa. Ọ̀kan lára àwọn tí a jọ ńgbé yàrá rí tí ó wa ńgbé ní Kansas si pè wá lati darapọ̀ mọ́ wọn ni ọdún nà fún àjọ̀dún sísí ọjọ́ sísọdẹ ẹyẹ àparò. Inú mí dùn lọ́jọ́ nà láti sọ pé ó kéré jọjọ.

A sì wà ní ojú ọ̀nà fún wákàtí máarún ti à ńlọ si Kansa, a gbádùn ọjọ́ nà ti a lọ sọdẹ, a si pa ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹyẹ. Sùgbọn nígbàtí a ńpadàbọ̀ lójú ọ̀nà si Tulsa, ẹnjínnì ẹ̀rọ ọkọ̀ ọ̀rẹ́ wa bàjẹ́. A sì wà láàrin ọ̀nà ti a kò mọ ibikankan tí gbogbo ọ̀nà náà dọ̀tí bẹ̀ẹ̀ si ni ó tún jìnàǹ díẹ̀ sí ilé. Tí ó bá jẹ́ wípé o ti lọ sí Kansas rí, nigbàna wa mọ bi ìlú nà ti yàgàn tó ilẹ̀ ti wá ńsú.

Ọ̀kanlọ́kan ni a sì ti rí iná ti om tàn. A lọ́ ile àgbẹ̀ kan láti lọ sọ ohun ti o sẹlẹ̀ sí wa àti ipò tí a wà. Ìyàlẹ́nu ńlá ni ó jẹ́ fún mi nígbàtí o sọ pé, "Ó da, mo maa gbé yín dé ilé ní alẹ́ yìí. Ma gbé ọkọ̀ tiyín sínú ọkọ̀ akẹ́rù ńla tèmi, ma sì gbe yín lọ sí ilé yín lásìkò kí ẹ ba le múra sílẹ̀ fún isẹ́ ọjọ́ Ajé." (Tí ó

sì jẹ́ pé Drenda fẹm bẹ̀rẹ̀ isẹ́ titun ni òwúrọ̀ ọjọ́ isẹ́ ní ilé ìta óunjẹ kan fún apákan àkókò/ìdajì ọjọ́, tí o si ti ńro pé ohun tí kò dára tóo ni láti pè wọ́n pé òun kò ní le wá ní ọjọ́ nà.)

Sí ìyàlẹ́nu, arákùnrin yi, tí a kò ti bá pàdé rí,wà wá lọ silé niTulsa ìrìn àjò wákàtí maárun ó sì tún yípadad lati máa lọ sí Kansas kim ilẹd ọjọ́ nada tó mọ́. Gbogbo òrú ni o fi wa ọkọ̀!

Mi o le gbàgbé irú ìwà aláànú bí èyí. Kò ti ẹ gba kọ́bọ̀ fún owó epo. Gbogbo ìgbà ni ma ma dúpẹ́ fún irú ènìyàn bẹ̀ẹ̀ nígbàtí mo bá ti ronú nípa rẹ̀, ma ma ronú nípa ẹ̀bùn àti ìwàrere rẹ̀.

Nígbàtí àwọn ènìyàn bá nronú nípa rẹ̀ wọn ó ma dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún inúrere rẹ̀.

Mo mọ̀ dájú pé o le ro irú ipò yí wò bákanna nínú ayé rẹ. Wa sì le rántí bí o ti se mọ̀ ọ́n lóore sí fún ìtọ́jú àti ìfẹ́ tí ẹnìkan fihàn ọ́. Ó da, nkan tí Páùlù ńgbìyànjú láti sọ fún ìjọ nìyìí pé inúrere wọn ti ńde ọ̀dọ̀ àwọn ènìyàn pẹ̀lú ọkàn tí Ọlọ́run ti ó sì mú kí wọn ma fi ìyìn àti ọpẹ́ fún isẹ́ ìsìn wọn síi.

**ÀWỌN ÈNÌYÀN YÓÒ DÚPẸ́ LỌ́WỌ́ ỌLỌ́RUN FÚN Ọ̀PỌ̀ OORE ÒFẸ́ TÍ Ó FIFÚN ÀWỌN Tí ÓNÍNÚRERE!**

Nígbàtí mo ti wam sọ́dọ̀ Krístì, mo wá rí pé ọkàn mi rò, ati pé nítòótọ mo ńsetọ́jú àwọn ènìyàn. Nígbàtí mo bá ri pé nkan tí o yẹ ní síse nìyí, mo ma fẹ́ sèrànlọ́wọ́, sùgbọ́n o má pinmílẹ́mí pé ọ̀pọ̀ ìgbà ni mi ò ní le se é nítoripé kò si owó tí mo le fi se.

Mo wá ri pé bí o se ri fún ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn na nìyí. Ìwọ kàn dìde kí o sọ̀rọ̀ jáde láàrin èrò kí o bèèrè fún ìtọ́sọ́nà, waam rí iye àwọn ti ó dúró dè ọ́ láti ràn ọ́ lọ́wọ́ àti rí ojú ọ̀nà.

Sùgbọ́n bí mo ti sàwárí rẹ̀ nínú Bíbélì, pé sísе onínúrere ní agbára ju bí mo ti se mọ̀ tẹ́lẹ̀ lọ. Tí o bá ka ẹsẹ yí nínú 2 korinti 9 ó se àfihàn ìlàna òfin ti ìjọba tí mo ti rò nípa ìfifunnị

> *Nítorí isẹ́ ìránsẹ́ ìsìn yìí kò kún ìwọ̀n àìní àwọn ènìyàn mímọ́ nìkan, ṣùgbọ́n ó túbọ̀ pọ̀ sí i nípa ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọpẹ́ sí Ọlọ́run.*
>
> *Nítorí ìdúró yin lábẹ́ ìdánwò isẹ́ ìsìn yìí, wọn yóò yin Ọlọ́run lógo fún ìgbọ́ràn yín ní gbígba ìhìnrere Kristi àti nípa ìlawọ́ ìdáwó yín fún wọn àti fún gbogbo ènìyàn.*

*Àti nínú àdúrà fún un yín, ọkàn wọn ń ṣe àfẹ́rí yín nítorí ọ̀pọ̀ oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ti ń bẹ nínú yín. Ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run nítorí aláìlèfẹnusọ ẹ̀bùn rẹ̀!*

—2 Korinti 9:12-15

Àwọn ènìyàn yóò dúpẹ́ lọ́wo Ọlọ́run fún ọ̀pọ̀ oore-ọfẹ tí o fifún àwọn onínúrere!

Kín ikan tí Páulùn sọ níbíyìí nítòótọ́ kí ó ba le yé wa, a ní láti túmọ̀ rẹ̀:

Pọ̀jùlọ túmọ̀sí: Iye nkan tótóbi tàbí tó wà ní ìpele gíga; tópọ̀ rékọjá, tayọ,tàbí ju bótiyẹlọ: Àwọn ètò ti ọ̀pọ̀ ohun tótóbi.[2]

Kínni nkan tí yóò jẹ́ tìrẹ nínú ọ̀pọ̀ ohun tótóbi yìí? Kínni nkan tí yóò ju bí ó ti se yẹ lọ àti òpò ohun tótóbi nínú ayé re? Oore-Ọ̀fẹ́ Ọlọrun ni!!!!!

Ó yá, níbáyìí a nílò ìtumọ̀ fún oore-ọ̀fẹ́.

**Oore-Ọ̀fẹ́ túmọ̀** sí àánú Ọlọ́run tí a kò tọ́ sí.

Èyíi ni ìtumọ̀ oore-òfẹ́ tí ó péwọ̀n, sùgbọ́n ó tún kéré sí ohun tí o ǹse gan. Jẹ́ kí nsọ ìtumọ̀ míràn tí ó dára fún ọ.

Ọ̀rọ̀ tí Wikipedia sọ nìyí nípa oore-ọfẹ mímó:

*Ohun tí ó wọ́pọ̀ nínú ẹ̀kọ́ Krìstíánì nipé oore-ọ̀fẹ́ jẹ́ àánú (ojúrere) ti Ọlọ́run fún ìran ènìyàn nípasè ríràn ọmọ rẹ̀ lati wá kú lórí igi àgbélèbú, èyí ni ó sì mú ìgbàlà ayérayé wá. Síbẹ̀síbẹ̀, ìtumọ̀ yìí nìkan leè má tó fún ohun gbogbo lòó fún nínú ìwé mímọ́. Fún àpẹẹrẹ, Lúkù 2:40 (Ẹ̀dà Ọba Jákọ́bù) "Ọmọ náà sì ń dàgbà, ó sì ń lágbára, ó sì kún fún ọgbọ́n: oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run sì ń bẹ lára rẹ̀" Nínú àpẹẹrẹ yí nígbàtí a bá nlo ìtumọ̀ ti oore-ọ̀fẹ́ bí àánú tí a kòtọ́sí kò mọ́gbọ́n dání pé Krístì tí kò lẹ́sẹ̀ má nílò èyí.*

*James Ryle ti dábàá pé "Oore-ọ̀fẹ̀ ni ìwàláayè agbára Ọlọ́run láti mú ọ jẹ́ ohun tí ó dá ọ fún láti jẹ́, àti se ohun tí ó pè ọ́ sí láti se." Ní ọ̀nà míràn, Bill Gothard na ti dábàá pé "Oore-ọ̀fẹ́ fún wa ní ìfẹ́ ọkàn wa àti agbára tí Ọlọ́run fún wa láti se ìfẹ́ rẹ̀." Àwọn ìtumọ̀ méjéjì yí ni ó mú ọgbọ́n dání ní ti gbólóhùn ọ̀rọ̀ oore-ọ̀fẹ́ jákèjádò inú Bíbélì.*[3]

---

[2] Dictionary.com

[3] https://en.wikipedia.org/wiki/Divine_grace

Ńítorínạ̀, a rí pé ohun tí Páulù ńsọ náà ni oore-ọ̀fẹ́, tàbí ìrónilágbára, láti serere. Ẹ̀bùn yìí, ẹ̀bùn oore-ọ̀fẹ́, ni a se àjọyọ rẹ̀ nítorí ó fún àwọn èniyàn ní agbára láti serere. Bẹ́ẹ̀ ni wọ́n se àánú, wọ́n bá àìní àwọn èniyàn pàdé, ó sì mú wọn sin Ọlọ́run.

Paúlù parí ọ̀rọ̀ rẹ̀ pẹ̀lú pé,"**Ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run nítorí alaílefẹnusọ ẹ̀bùn rẹ̀!"**

Ó dára, ó ku ìtumọ̀ kan. Gbólóhùn ọ̀rọ̀ yìí alaílefẹnusọ túmọ̀sí, bí ó ti se fi hàn ní kedere, pé kò sí àwọn ọ̀rọ̀ náà *tí* a lè fisàpèjúwe rẹ̀. Bí Paúlù ti sọ pé bí ẹ̀bùn oore-ọ̀fẹ́ ti se dára tó nìyìí, *rékọjá àwọn ọ̀rọ̀,* ati pàápa àwọn tí ó bá se isẹ́-ìránsẹ́ fún nípa ìsúná tí ó pèsè.

Agbára na nìyí tí o le tú ọ sílẹ̀ kúrò nínú ìgbèkùn àilówó. Agbára yìí, oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run, wà fún gbogbo ẹnití ó gbàgbọ́.

Sùgbọ́n ìsòro tí ó wà nìyíí. A le lo ọ̀pọ̀ àsìkò láti máa sọ̀rọ̀ nípa ohnu tí Paúlud sọ láti se—láti *funni.* Sùgbọ́n tí a kò bá ní òye oore-ọ̀fẹ́, ìrónilágbára láti serere nípa agbamra Ọlọ́run, a le pàdánù ìkórè ti Ọlọ́run ti pinnu fún wa. Yó wá dàbí gbíngbin ọgbà rẹ̀ sínu igi àti gbé si abẹ́ ibòòji igi ńlá—kò sí òòrùn, kò sí agbára láti mú èsi tí o fẹ́ mú jáde wá.

Èmí àti Drenda yóò ka àwọn ìtàn inú Bíbélì níbi tí agbára Ọlọrun hàn tí ó sì yí ipò náà padà pátápátá sí rere. Mo gbà pé a gbọ́ irú àwọn ìtàn yìí díẹ̀ náà tí ó sẹlè nínu ìjọ wa bí a ti ńdàgbà. Tí kò bá si ti ìgbàlà, kò sí ẹnìkan tí o máa sọ̀rọ̀ nípa bí a ti se le mú oore ọ̀fẹ́ wá sínum ipò náà.

Nísisiyii, ó ye mi pé ìgbàlà wa ni nkan tí ó se pàtàkì jùlọ. Sùgbọ́n bí mo ti sọ, mo nìlò oore-ọ̀fe yí kannà láti le sisẹ́ níbi ipa gbogbo nínú ayé mi, sùgbọ́n mi ò mọ̀ báwo ni màa ti sé. Nítorí àinìmọ̀ mi, a kò ní owó lọ́wọ́, se àìsàn, àti rẹ̀wẹ̀sì. A mọ ti ìgbàlà—a ní ìgbàlà ayéraye nípa ti wa—Sùgbọ́n a kò mọ̀ tàbí ní òye bí à ti se le mú ọ̀run wá sínu ayé wa ati se àfihàn agbára tí Ọlọ́run. Bí mo ti sọ fún ọ, àwa ni a ńpa owó!

Sùgbọ́n ohun tí Olúwa nsọ fún mi ni ọjó nà nìyí nígbàtí ó nbámi sọ̀rọ̀ nípa ìjọba, "*Ó wà nínu ìdọ̀tí yìí nítorití o kò ti kọ́ bí ìjọba mi ti sisẹ́!"*

Ní ọ̀nà míràn ewẹ̀, Ohun tí ó ńsọ nipé mi ò ti mọ̀ bí a ti ńpàsẹ bí Ọba

[4] Ìwé Ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ ti èdè Gẹ̀ẹ́sì àtúnse kaàrún ti Amérícám Héritagè.

lóri ilẹ̀ ayé. Mi ò ti kọ́ báwo ni tàbim bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé mo le seé. Nkò ní òye bí mo ti se le mú nínú ore ọ̀fẹ́ nà, agbára Ọlọ́run.

Ha, ọ̀rọ̀ tí a sọ pọ̀ jù bẹ́ lọ nígbàtí Ọlọ́run nbámi sọ̀rọ̀ nípa Ìjọba. Ó tẹ̀síwájú láti sọ pé, "*Ìjọ mi ngbé gẹ́gẹ́ bí àwọn ọmọ Ísraẹ́lì ti se nígbàtim wọ́n wà lóko ẹrú tí wọ́n mọ bíríkì fún Farao. Ẹrú ni wọ́n! Àwọn ènìyàn mi wà nínum gbèsè, mo si fẹ́ kí wọ́n bọ́!*"

Jẹ́ki nsọ kókó kan níbáyi: O kò le di òmìnira laí títí wàá fi bọ́ lọ́wọ́ àìlówó lọ́wọ́. Gẹ́gẹ́bi èmi ati Drenda ti sọ láti bí ọgbọ̀n ọ̀dún sẹ́yìn, o kò le mọ̀ laí ẹnití o jẹ́ gan ati le má a rìn nínú èrèdí tẹ̀mí fún ayé rẹ tí wàá fi sàtúnse ọ̀rọ̀ lórí owó.

Jẹ́ kin tún sọ kóko yí bákannà**: O LE DÒMÌNIRA!** Ma fi hàn ọ́, bẹ́ sì ni ẹgbẹgbẹ̀rún àwọn ẹlòmíràn pẹ̀lú. Oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run wà níbẹ̀ láti ràn ọ́ lọ́wọ́. Àwọn nkankan wà tí a pè ọ́ sí láti se tí o kò sì le rí se yọrí gẹ́gẹ́ bí ẹrú. O gbọdọ̀ gba dòmìnira àti lówó lọ́wọ́ kì íse fún ara rẹ adti ẹbí rẹ nìkan sùgbọ́n bakanna kí àwọn ènìyàn le rí ìjọba ti Ọlọ́run pé ó nsisẹ́ nínú ayé rẹ, bí igi èso tim a gbìn tí ó ní èso pínpọ́n lórí tí yóò pe àwọn ènìyàn wá sínú ìjọba.

**ÀWỌN ENÌYÀN ŃWÁ ÀWỌN ÌDÁHÙN. WỌ́N NWÁ OHUN TÍ SẸ TÒÓTÓ KIRI. WỌ́N FẸ́ RÍ ÌJỌBA NÍ KÍAKÍA ÀNÍ KÌ ÍSE Ẹ̀SÌN..**

Awọn ènìyàn ńwá àwọn ìdáhùn. Wọ́n ńwá ohun tí nse tòótọ́ kiri. Wọ́n ńfẹ́ láti rí ìjoba Ọlọ́run ní kíakía àní kì íse ẹ̀sìn.

Jẹ́ kí sọ fún ọ nípa àwọn ọ̀rọ̀ tí èmi pẹ̀lú nọ́ọ̀sì kan jọ sọ ní àná. Ó da, àwọn nọ́ọ̀sì méjì ti ẹ̀ ni wọ́n.

Mọ̀mọ mi ti pé ọmọ ọdún méjìdínláàdọ́rún wọ́n sì nse dáadá, sùgbọ́n wọ́n nílò ìrànlọ́wọ́ ní àyíká wọn, mo fẹ́ kí o fi ojú inú wòó. Nim ojọ́ tá nsọ yìí, mo ní láti gbé wọn lọ rí àwọn dọ́kítà fún àyẹ̀wò bí wọ́n ti pinnu láti pàdé.

Bí mo se ti ńbá nọ́ọ̀sì sọ̀rọ̀ níbi ìpàdé àkọ́kọ́, ó wá nbí mi léèrè pé isẹ́ kínni ni mò ńse. Mo sọ fún nípa ìjọ wa àti pẹ̀lú nípa ilé isẹ́ tí ìsúná mi àti bí a ti se ńran àwọn ènìyàn lówó láti bọ́ kúrò nínú oko gbèsè. Ó dá, ó lákíyèsí ohun tí mo sọ. Ó tẹ̀síwájú lati sọ fún mi pé òun wà nínú wàhálà, òun jẹ gbèsè, òun kò sì mọ bí òun yóo ti se bọ́ kúrò nínú rẹ̀.

Nígbàti mo lọ sí ọ̀dọ̀ dọkítà ẹlẹ́keji ní ọjọ́ nà gan, mó ba nọ́ọ̀sì ti mo

pàdé nibẹ̀ sọ ọ̀rọ̀ kanna. Omijé fẹ́è le máa jábọm lójú rẹ̀ bí ó ti nsọ fún mi nípa ipò tí etò ìsúná rẹ̀ wà.

Ọ̀rẹ́, kò jọ ara wọn. Bí Amẹ́ríkà se ńgbé lóde òníí nìyìí. Ó wu ọkàn mí ḷati ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́ àti ní òye pé ọ̀nà àti gbé ayé tó dára wà—ọ̀nà ti Ìjọba Ọlọ́run.

Nígbàtí èmi àti Drenda bẹ̀rẹ̀ sí ní kọ́ nípa Ijọba Ọlọ́run tí a sì bẹ̀rẹ̀ sí ní se ohun tí Ọlọ́run ńkọ́ wa nípa Ijọba, ayé wa yípadà lọ́nà tó lágbára. Àwá bẹ̀rẹ̀ sí ni rí oore-ọ̀fẹ́ tí Paúlù ńsọ nípa rẹ̀ tí o farahàn nínú ayé wa.

Ní alẹ ọjọ́ kan, mo lá àlá láti bẹ̀rẹ̀ oko òwò ti wa láti fi ma ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́ lati lè bọ́ kúrò nínú gbèsè. Iwà wèrè ni, àbí? Apà ọmọ tí kò mọ ohun tí yóò fowó se tí ó wá dá ilé isé tí nfi ọ̀nà àti bọ́ lóko gbèsè han àwọn èniyàn lọ. Ọlọ́run nìkan, ló mọ̀?

O le má bèèrè pe, "Báwo ni o ti se ńselẹ̀? Báwo ni o ti se mọ̀ bí wọn ti se le bọ kúrò ní oko gbèsè tí ìwọ gan yóò fi le ran àwọn míràn lọwọ́ láti bọ́ nínú gbèsè?" Ìbéèrè ńlá nìyìí!

Níkúkúrú, Ẹ́mí Mímọ́ ni ó fi hàn mí bí mà ti seé.

Lótítọ́, àwọn nkan míràn wà tí mo ní láti kọ́, mo sì nílò àwọn tí wón ó má kọ́ mí lórí bí ma ti se bẹ̀rẹ̀ ilẹ̀ isé mi, Sùgbọ́n Ẹmí Mímọ ni o ní ìlànà ète tó dáyàtọ̀ fún ìlọsíwájú àti àwọn ọ̀nà tí a le gbà láti ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́. Ilé isé nà sì bẹ̀rẹ̀ ohun ni ó sì mú kí ìsúná wa dì òmìnira.

Kódà láìsọ mo mọ nkan tí ò ńrò: À bá ma gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó fún ìrànwó nà tí ó bá jẹ́ pé gbogbo owó tí a nílò ní láti jẹ́ lọ́fẹ.

Nope. Bí mo ti sọ, Ẹ̀mí Mímọ́ fún wa ní àwòkóse oko-òwò aláìlẹ́gbẹ́, ohun sì nìyìí:

A ńsisẹ́ pẹ̀lú àwọn oníbárà wa LỌ́Ọ̀FẸ́.

Báwo ni mo ti se le díyelé ẹniti tí ó ntiraka láti san àwọn gbèsè owó tí ó jẹ tí yóò fi bọ́ nínú rẹ̀? Rárá, èmi ò le sé. Ọlọrun fún mi ní ọ̀nà ti ó dá yàtọ̀ fún àtìlẹ́yìn owó níná ní ilé isẹ mi. Kò ti sí kò sì ní sí dídíyele fún ilé isé mi láti mú ètò àkànse fún àwọn oníbarà wa dàgbà láti bọ́ kúrò nínú gbèsè. Ohun tí ilé isẹ mi mọ̀ lámọ̀já ni láti fi hàn àwọn oníbára wa bí wọ́n o ti se bọ́ kúrò nínú gbèsè ní àárin ọdún méje, pẹ̀lú ilé ya wọn pàtàkì júlọ láìjẹ́ wípé wọ́n pàrò owó òyà tí ńwọle fún wọn.

Kì íse àwọn oníbára wa ni ó sàtìlẹ́yìn fún wa sùgbọ́n àwọn ilé isẹ bí dọ́sìnì ni ó wà ní kàlẹ̀, àwọn abánitajà àti àwọn akọ́sẹ́mọsẹ́ tí a ti yàn láti

máa wá ọnà àbáyọ àti sàtúnse àwọn àsàyàn fún àwọn oníbara wa. Wọn tìwáléyìn láti máa bá wa sọ fún àwọn oníbarà wa nípa ilé isẹ wa.

Fún àpẹẹrẹ, nínú ètò ìlànà ètò àtúnse, tí mo bá mọ pé ilé isẹ XYZ le dín owó adójútòfo oníbárà mi sí bí ìdajì, màá sọ fún wọn kí wọn lo sí ilé isẹ XYZ. Àwọn oníbárà mi yóò wá lọ bá ilé isẹ XYZ sọ̀rọ̀ fúnra wọn, wọn ó sì pinnu ní ọkàn wọn bí wọn bá ti fẹ́ bá XYZ se papọ̀ nínú ẹ̀dínwó bí ara ètò sísàtúnse wọn tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́.

Nítorínà,níti àwọn oníbára, ọ̀fẹ́ ni ohungbogbo. Mo sì mọ̀ dájú pé èyí ni ojúse wa àkọ́kọ́ ní fimfọwọsí dídàgbàsókè ilé ise wa. Lọ wo ilé isẹ wa ní orí ìtàkùn yìí forwardfinancialgroup.com.

A tún máa ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́ láti mọ ohun tí à npè ní ìdókòwò àìléwu. O dàbí kí enìyàn se ìdókòwò tí kò ní ewu owó ọjà wálẹ̀ ni tàbí jíjí owó idfẹ̀yìntì yín gbé.

Mo sọ gbogbo nkan yìí láti fi yé yín pé léke ọgbọ̀n ọdún tí a ti wà, à ńsòrò nípa ẹgbẹgbẹrún àwọn ènìyàn, a kò tí rí ohun àbùkù tí òpò àwọn aram Amẹ́ríkà ńbá ara wọn.

Apeẹrẹ kan nìyìí tí ó hàn sí mi àti àpèjúwe bí ọ̀pọ̀ àwọn ara Amẹ́ríkà tí ngbé ayem wọn.

Arabìnrin kan pè mí láti wá bẹ òun wò, pé òun nílò ìrànwọ́ lórí gbèsè tí ó jẹ. Emi àti ọ̀kan lára àwọn alábàsisẹ́pọ̀ mi, lọ láti pàdé rẹ̀, mo jókòó níbè laífẹ́ má gbá gbogbo ohun tí ó nsọ gbọ́ nígbàtí ó sàlàayé bí nkan ti se rí fún un. O ní orisi káàdì ẹ̀yáwó bíi mejìlélọ́gbọ̀n, gbogbo rẹ̀ ni gbèsè wà lórí rẹ̀. (Bẹ́ẹ̀ni, o gbọ́ ohun tí mo sọ dáda—ó ní káàdì èyáwó méjìlélọ́gbọ̀n.)

O ti se àseyọrí láti kọ́ ọgbà ẹ̀wọ̀n fún ara rẹ̀, ó wá ńbèrè kọ́kọ́rọ́ tí yóo fi sílẹ̀kùn jáde lọ́wọ́ tèmi. Nínú ọkàn mi lọ́hun, mo ní ìdáhùn rẹ̀ rọrùn: Má lo àwọn káàdì ẹ̀yáwó yí mọ́. Ibẹ̀rẹ̀ ní ohun àkọ́kọ́ nìyí. Mo wá sọ fún kó gé káadì ẹ̀yáwó kúrò kó dúró lórí iye tí owó òyà rẹ̀ jẹ́ tàbí iye owó tí ó bá nwọlé fún ni níná. Mo wá fún ní isẹ pàtàkì kan fún pé kí o kọ gbogbo nkan tí ó má ńfi owó se sílẹ̀ kí nba le mọ ibití màá ti bẹ̀rẹ̀ láti gbàá ní ìmọ̀ràn. Mo tún gbàá níyànjú láti máa lo dẹ́bítì kaádì (káàdì tí yóò maa sọ iye tí ó ná ní ojú ẹsẹ̀ fun tàbí iye tí gbèsè rẹ̀ ti dà) dípò kí ó máa lo kaádì ti bánkì láti le yàgò kín nkan kó má buru si fún un.

Níbití mo ti ńdáàbá kí ó má lo káàdì ẹ̀yáwó rẹ̀ mọ́, ó bú sẹ́kún ni ó wá

bèrè ìbéèrè tí ó yanilẹ́nu yìi: "Báwo ni màá se wá rí owó ra àwọn bàtà?

Sé o gbọ́ ohun tí mo sọ dáadáa? Kò ní owó tí ó tọ́ láti ra óunjẹ, sùgbọ́n ó sunkún nítorí bàtà?

O lerò pé arabìnrin nà kò gbádùn tó. Nínú ara àwọn káàdì ẹyáwó tí ó ní, ó dàbí pé kò gbádùn lóòtọ́ọ́. Sùgbọ́n fún láti wà nínú ẹ̀wọ̀n ti tì ìsúná, kò rí bẹ̀. Wòó bí wọ́n ti ńse ní Amẹ́ríkà nísisinìyí:

- 57% àwọn ènìyàn ni wọn kò ní ẹgbẹ̀rúnkan pọ́ùn ní bánkì[5]
- 44% wọn níye ni wọn kò le san irinwó pọ́ùn iye owó tí wón jẹ.[6]
- 23% ará Amẹ́ríkà ni wọn ò le san owó tí wọ́n jẹ ni ososù tí wọ́n wá ńsubú sínú gbèsè ní ososù.[7]

Ẹ̀yin ọ̀rẹ́, adwọn ara Amẹ́ríkà dàbim nkan tim Ọlọ́run sọ fún mi pe—ẹrú ni wọ́n.

Ronum nkan tí ẹrú ńse.

- Kò sisẹ́ fún ara rẹ̀. Bíótilẹ̀jẹ́pé ó nsisẹ́ àti rí èrè, ó ńfi èrè ránsẹ́ si àwọn ayánílówó ni ososù, tí ó wá ńfi ìwọ̀nba tí ó tó sílẹ̀ fún àwọn ẹbí rẹ̀ láti lò ní osù tónbọ̀.
- Ẹrú ńgbé nínú ilé tí kì íse tirẹ̀ (tí ó túmọ̀ sim pé wọ́n nyáa

[5] Ray Hanania, "57% ará Amẹ́ríkà ni wọn kò ní tó ẹgbẹ̀rúnkan pọ́ùn nípamó, March 31 2021, SuburbanChicagoland.com. (Ọjọ́ Kọkànlélọ́gbọ̀n Osù Ẹránnà 2021)

[6] Joseph Lawler, "44% níye ni wọn kò le san irinwó pọ́ùn iye owó tí wón jẹ "Washington Examiner, May 19, 2017 (Ọjọ́ Kọkàndínlógún Osù Obìbi, 2017).

[7] Megan Leonhard, Bọ́ lóko gbèsè pátá" ní May 24, 2019. (Ọjọ́ Kẹ̀rìnlélógún Osù Obìbí 2019).

gbé ni).

- Wọ́n nwa ọkọ̀ tí kì se ti wọn lọ sí ibisẹ́ láti san owó ilé tí kìse àwọn lóni ní.

- Wọ́n wọ àwọn asọ tí wọ́n rà láwìn pẹ̀lú kaádì ẹ̀yáwó láti lọ síibisẹ́, ati san owó ọkọ̀ àti ilé tí kì ise àwọn ni ó ni, pẹ̀lú ẹ̀yáwó owó omo ilé ìwé ti wọ́n sì nsan lati bi ogún ọdú sẹ́yìn.

Sé ohun tí mò nsọ yé ọ.

*Ọlọ́rọ̀ ṣe olórí olùpọ́njú,ajigbèsè sì ṣe ìránṣẹ́ fún ẹni tí a jẹ ní gbèsè.*

—Iwe Owe 22:7

Njẹ́ o mọ̀ pé ọ̀pọ̀ ènìyàn ni kò nífẹ̀ sí àwon isẹ́ tí wọ́n ńse? Bíotilẹ̀jẹ́pé àgbélé wọ̀n kan ní Gallup poll sọ pé ìdá máàrún lélọ́gọ́rin àwọn òsìṣẹ́ ni wọ́n kọ́rí́ra iṣẹ́ tí́ wọn ńse.[8]

Kí́lọ́ wá́ dé́ tí́ wọn ńfi ńsiṣẹ́ níbití́ wọn gbé́ ńsiṣẹ? Nítorípé́ ẹrú́ ni wọ́n, ẹrú́ kò̀ sì̀ ní́ à̀sà̀yà̀n? O wù̀mí́ tà̀bí́ kò̀wù̀mí́? Bẹ́ẹ̀ni!

Nitorí́nà̀, sé́ ọ̀nà̀ à̀bá́yọ kú́rò̀ ní́ oko ẹrú́ wà̀?Bẹ́ẹ̀ni

Má́ gbà̀ mí́ gbọ́? Jẹ́ kin fi hà̀n ọ́.

*Nítorí iṣẹ́ ìránṣẹ́ ìsìn yìí kò kún ìwọ̀n àìní àwọn ènìyàn mímọ́ nìkan, ṣùgbọ̀n ó túbọ̀ pọ̀ sí́ i nípa ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọpẹ́ sí Ọlọ́run.*

*Nítorí ìdúró yin lábẹ́ ìdánwò iṣẹ́ ìsìn yìí, wọn yóò yin Ọlọ́run lógo fún ìgbọ́ràn yín ní gbígba ìhìnrere Kristi àti nípa ìlawọ́ ìdáwó yín fún wọn àti fún gbogbo ènìyàn.*

*Àti nínú àdúrà fún un yín, ọkàn wọn ń ṣe àfẹ́rí yín <u>nítorí ọ̀pọ̀ oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ti ń bẹ nínú yín</u>. Ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run nítorí aláìlèfẹnusọ ẹ̀bùn rẹ̀!*

---

[8] Sara Burrows, ìdá máàrún lélọ́gọ́rin àwọn Eniyan ni wọ́n Kórira Isẹ́ tí wọn ńse,ni Gallup poll sọ," September 22, 2017, (Ọjọ́ kejìlélógún Osù Ọwẹ́wẹ 2017), returntonow.net.

—2 Korinti 9:12-15

Ẹ jẹ́ kí á lọ fojú wo ìbéèrè yìí—Oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run, ìrónilágbára láti serere!

Ẹ jé kí a tún ní àkiyèsí pé ọ̀tá fẹ́ kí o wà nínú gbèsè kí o sì má rí ọ̀nà àbáyọ rárá. Idí sì nìyí tí 1.1 trílliọ́nù kaádì ẹ̀yáwó gbèsè se wa ni U.S.[9] Ohun náà ni ó fàá ìdíti ànfàní gbígba kaadì ẹ̀yáwó bi bíllíọnù mẹ́ẹ̀rin sí mẹ́jọ se wà ni ọdọdún.[10]

Ẹnìkan fẹ́ kí o di onígbèsè, kì íse àwọn ilem ìfowópamọ́ nìkan ati àwọn alágbàtà tí wọ́n nbẹ̀ ọ́ kí o ra káadì ẹ̀yáwó.

Sàtánì mọ̀ pé bí òun bá le mú ọ wọ oko gbèsè, o kò nim le rìn nínú àyànmọ́ tẹ̀mí rẹ mọ́ lái, tí ó sì mọ̀ pé yóò fa ohun tó léwu nínú idjọba rẹ̀.

Nítorínà, jẹ́ kí nsàtúnyẹ̀wò fún bí ìsẹ́jú kan. A ko ìwé yi nipa jíjẹ́ oninúrere, àbí? O da, bẹ́ẹ̀ni àti bẹ́ẹ̀kọ́. Bẹ́ẹ̀ni, a o lọ sọ̀rọ̀ nipa gbogbo àwọn ànfàní ti ìfifún àti jíjẹ́ oninúrere fún ìgbà díẹ̀. Sùgbọ́n ìfifúnni fún ara rẹ̀ kì íse ìdáhùn. Oní láti ní ìmọ̀ bí o ti se le fọwọ́ba wọnú oore-ọ̀fẹ́ nà, agbára Ọlọ́run.

Nítoríbẹ̀, jẹ́ kí ntún sọ lẹ́ẹ̀kansi: àgbékalẹ̀ ìfifúnni nípasẹ̀ ara rẹ̀, bí i àgbẹ́kalẹ̀ ni kì íse kọ́kọ́rọ́. Ara rẹ̀ na ni lóòtó, sùgbọ́n ìwọ àti èmi nílò agbára tí ó kọ́já òye, tí ó jú bẹ lọ tí ìrólágbára láti serere tí nse oore-ọ̀fẹ́.

Dustin ati Kendall sàwárí nkan tí mò nsọ̀rọ̀ nipa rẹd. Ọdọ́ ni tọkọtìyàwom wọn tí wọ́n kò fi bẹ́ẹ̀ ní òye pé àwọn nílò oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run nínú ètò ìnáwó wọn títí di ìgbad tí wọ́n bá ara wọn nínú ìdọ̀tí. Tí wọn sẹ̀sẹ̀ rí oko-owò kan tí wọ́n sì kówó le lóri. Tí ó sì ná wọn tó ọ̀kẹ́ méje abọ̀ pọ́ùn, ti gbogbo rẹ̀ si bọ́ sí gbèsè.

Nínú osù tí wọ́n ra oko-òwò wọn gan ni àwọn IRS se àgbéyèwò ìwé isẹ́ wọn tí wọ́n sì ní kí wọ́n san ẹgbèrúnmẹ́talélàádọ́ta pọ́ùn owó orí. Dustin sọ pé àwọn bá ara àwọn nínu gbèsè tó lé ní ọ̀kẹ́ mẹ́wá pọ́ùn tí kò sì mọ ọ̀nà àbáyọ, pàápá nígbàtí nkan ti wá le kòkò ní ti ètò ìsúná wọn kí wọn tó ra oko òwò na.

Wọ́n sẹ̀sẹ̀ yá owó tí wọ́n fi san owó ìtọ́jú àbíkẹ́hìn wọn ní ilé ìwòsàn

[9] Raynor de Best, Nọ́mbà Kaádì Ẹyáwó àti Dẹ́bítì Káadì ni U.S.2012-2018" Ọjọ́ kẹrìndínlógún Osù Ọ̀pẹ.2020, statisa.com/statistics

[10] Bob Bryan, Ọjọ́ kẹrìnlélomgún, Osu Belu, 2015 businessinsider.com.

ni, àwọn ayẹ̀wó owó wò ti sún wọ́n dé ògiri nítorí owó, Dustin sì ńwá gbogbo ọnà fún àbáyọ. Lẹ́yìn tí ó ti wá a káàkiri, ó wá rí ibití wọn ó ti yáa ní ọgbọ̀n pọ̀ùn láwìn ó sì lọ láti mọ ohun tí ìyàwo rẹ̀ rí sí i. Nígbàtí kò mọ̀ pé Kendall ti nka iwé àti se àsàrò lórí ìwé mi kan, *Yíyí Ètò Ìsúná Rẹ Padà: agbára ti Ìsinmi*, ti ohun na soro nipa ifowoba sinu oore-ofe Olorun.

Nigbati Dustin wá bá a láti sọ fún un nípa ẹ̀yáwó nà, ó ba Kendall inú jẹ́, ó lérò pé ó máa yípadà sọ́dọ̀ Ọlọ́run ju jíjẹ gbèsè lọ. Ó pinnu láti bá sọ̀rò àti gbàá níyànjú láti ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú Ọlọ́run. Tayọ̀tayọ̀, ni Dustin fi gba ọgbọ́n ìyàwó rẹ̀.

Bí wọ́n ti ńgbàdúrà, wọ́n gbọ́ tí Ẹmí Mímọ́ sọ fún wọn láti lọ fúnrúgbìn. Bẹ́ẹ̀ni lótítọ́, ní àkòkò na, wọn kò ní iye tí Ọlọ́run fi hàn wọ́n láti fi se ìfifúnni lọ́wọ́, wọ́n sì lọ se isẹ́ fún ọjọ́mejidínlọ́gbọ̀n kí wọn le ní owó tótó láti se ohun tí Ọlọ́run sọ fún wọn láti fúnrúgbìn.

Esì àbájáde? Isẹ́ wọn tún bẹ̀rẹ̀.

Láàrin ọdún tó tẹ̀le wọ́n san gbèsè ẹgbẹrúnmárùndínlọ́gọ́sán pọ̀ùn nínú gbèsè Dustin ní owó tí òun rí jẹ́ ìlópo MÉJÌLÁ iye owó tí òun tí máa rí tẹ́lẹ̀ lọ kódà ní ayem òun!

Dustin ati Kendall ti wádi bí ìjọba Ọlọ́run ti se ńsisẹ́ nígbogboìgbà!

Kínni ìdáhùn wọn? Ijọba àti oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run!

Kínni ìdáhùn rẹ? Ijọba ati oore- ọ̀fẹ́ Ọlọrun!

ORÍ KEJÌ

# ÌDÁHÙN: ORE-Ọ̀FẸ́

Nínú orí ẹ̀kọ́ tí a kà tán, a sọ̀rọ̀ nípa bí inúrere se nípa tẹ̀mí nínú ayé ènìyàn—bí o ti rọ ọkàn àwọn ènìyàn pẹ̀lú ọpẹ́ sí ọ àti sí Ọlọ́run. A tún gbé ohun tí Paúlù sọ yẹ̀wò pé, agbára láti ní inúrere ni èsì àbájáde ti ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run nínu ayé wa.

> *Àti nínú àdúrà fún un yín, ọkàn wọn ń ṣe àfẹ́rí yín* nítorí ọ̀pọ̀ oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ti ń bẹ nínú yín. *Ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run nítorí aláìlèfẹnusọ ẹ̀bùn rẹ̀!*
>
> —2 Korinti 9:14-15

A sọ̀rọ̀ nípa bí Paúlù ti se tẹnumọ́ gbólóhùn ọ̀rọ̀ yìí *ọ̀pọ̀* nígbàtí ó sàpejúwe ore-ọ̀fẹ́ tí Ọlọ́run fi fún wa ni láti serere. A wá ri pé ore-ọ̀fẹ́ túmọ̀ sí agbára tí ó jù bẹ lọ láti se àseyọrí nínú ǹkan Paúlù wá pèé ní ìronilágbára ore–ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ní ẹ̀bùn aláìlefẹnusọ! Mo lérò pé ẹnikẹ́ni ní ó yẹ kó gbà pé tí Ọlọ́run, tìkararẹ̀ ni yóò bá ran ni lọ́wọ́ láti serere nínú ayé, yóò jẹ́ ànfàní tó yani lẹ́nu.

Láti ran ọ́ lọ́wọ́ kí o le gbá bíí ohun tí Ọlọ́run fẹ́ se nínú ayé rẹ àti agbára tí ó tóbi jùlọ tí ó wà fún mu ́, jẹ́ kí a fi àwọn ẹsẹ díẹ̀ sílẹ̀ kí á sì lọ bẹ̀rẹ̀ sí ní kàá láti ẹsẹ kẹfà.

> *Ṣùgbọ́n èyí ni mo wí pé: Ẹni tí ó bá fúnrúgbìn kín ún, kín ún ni yóò ká; ẹni tí ó bá sì fúnrúgbìn púpọ̀, púpọ̀ ni yóò ká. Kí olúkúlùkù ènìyàn ṣe gẹ́gẹ́ bí ó ti pinnu ní ọkàn rẹ̀; kì í ṣe àfi ìkùnsínú ṣe, tàbí ti àìgbọdọ̀ má ṣe; nítorí Ọlọ́run fẹ́ onínúdídùn*

*ọlọ́rẹ. Ọlọ́run sì lè mú kí gbogbo oore-ọ̀fẹ́ máa bí sí i fún yín; kí ẹ̀yin tí ó ní ànító ohun gbogbo, nígbà gbogbo, lè máa pọ̀ sí i ní iṣẹ́ rere gbogbo. Gẹ́gẹ́ bí a ti kọ́ ọ pé: "Ó tí fọ́nká; ó ti fi fún àwọn tálákà; Òdodo rẹ̀ dúró láéláé.*

*Ǹjẹ́ ẹni tí ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ, yóò fi irúgbìn fún un yín, yóò sì sọ ọ́ di púpọ̀, yóò sì mú èso òdodo yín bí sí i. Bẹ́ẹ̀ ni a ó sọ yín di ọlọ́rọ̀ nínú ohun gbogbo, fún ìlawọ́ yín gbogbo tí ń ṣiṣẹ́ ọpẹ́ sí Ọlọ́run nípa wa.*

—2 Korinti 9: 6-11(EHV)

Níbáyìí, a ti dé ibití ǹkan ti wá mórí eni yá gan!

A rí gbólohùn ọ̀rọ̀ yí kannà *ore-ọ̀fẹ́* tí a lò níbiyí, yàtọ̀ sí tinú ẹ̀kọ́ yí tí Paúlù ti lo ẹ̀yán ọ̀rọ̀ *gbogbo* láti ran àwọn tí ó ńkaa lọ́wọ́ kí o le ye wọn pé GBOGBO agbára Ọlọrun ni ó wà nínú ọ̀rọ̀ ore–ọ̀fẹ́ yìí. Ohun tí Paúlù fẹ́ kí ó yé wa nípa ìfifún ni àti gbígbà níbíyi nipé ní ìwọ̀n ìgbàtí o ba ti fifúnni, gbogbo ore–ọ̀fẹ̀ ti Ọlọ́run ni o wà láti mú ìkórè nà wá.

Gbogbo ore–ọ̀fẹ́ Ọlọ́run túmọ̀sí pé gbogbo agbára Ọlọ́run, ọgbọ́n Rẹ̀, ojúrere, àti òye sì ti wà fún ọ láti le kó ìkórè lórí èso na. Emi o mọ tìrẹ, sùgbọ́n ó fún mi láyọ̀!

Sùgbọ́n èyí kò wá túmọ̀ sí pé ìkórè náà yóò sẹlẹ̀ bẹ́ẹ̀ fúnra rẹ̀.

Tí àgbẹ̀ kan tí ó ní ọrọ̀ gan tí ó ní owó lọ́wọ́ bá sọ fún ọ pé òun yóò yá ọ nim gbogbo àwọn irinṣẹ́ tí òun fí ndáko, tí ó tó míllíọnù dọ́llà, láti fi dá oko àti kí o kó àwọn èrè oko náà, tí o si jẹ́ pé ìwọ kò mọ ohunkóhun nípa oko dídá, kò le mú èrè kankan wá fún ọ.

Gbogbo agbára Ọlọ́run ti wà fún wa, sùgbọ́n àwa nà ní ojúse ti wa láti se, gẹ́gẹ́ bí àgbẹ̀ ti mọ̀ pé láti dá oko ní nkan tópọ̀ se ju kí á kàn fúrúgbìn sí orí ilè lọ.

**TÓJÚ OKO-ÒWÒ TI ỌLỌ́RUN, YÓÒ SÌ TỌ́JÚ TÌRẸ NÁÀ.**

Níbáyí, ohun gbogbo tí mo fẹ́ kí o mọ̀ nipé gbogbo agbára ti Ọlọ́run ni ó wà fún wa kì íse láti le ràn ọ́ lọ́wọ́ nìkan kó ìkórè lẹ́yìn tí o ti fúnrúgbìn sùgbon bákanna láti ràn ọ́ lọ́wọ́ à ti mọ nígbàwo àti níbo gbìn. Ati nitori nkan wonyii, kí o sì ní owó tí kòlópin fun ọjọ́ iwamjú!!!!

Níbáyí a ní láti gbé ìgbésẹ̀ síwájú síi kí á sì sọ̀rọ̀ nípa ìfihàn kedere

nínú ẹ̀kọ́ yìí àti sí ìdí tí ó fi yẹ kí ání owó.

> *Ọlọ́run le mú kí gbogbo ore-ọ̀fẹ́ wà ní àkúnwọ́sílẹ̀ fún wa, nínú ohungbogbo àti nígbàgbogbo, wà ni ohungbogbo tí o nílò, wa sì ní àkúnwọ́simlè nínú isé rere gbogbo.*

Arí ohun àkọ́kọ́ tí Ọlọ́run kọ́ sọ ni kí o ní ohun gbogbo tí o nílò. Kíyèsi pé kì íse nípa owó nìkan. Ó ní nínú ohnu gbogbo àti ní ìgbàgbogbo! Gbogbo ìgbà ni mo máa ńsọ nị ọ̀nà yií, "ìwọ máa tọ́jú iṣẹ́ ti Ọlọ́run, òun náà yóò sì maa tọ́jú tìrẹ" Nítorínà. nínú ohungbogbo àti ní ìgbà gbogbo" Ohun tí ó túmọ̀ sí sí mi ni wípé o kò le lọ lásán, ohun tí o wulẹ̀ kó selè nínú ètò ọrọ̀ ajẹ́. Nígbàtí Ọlọ́run bá sọ pé ohun má bá àiní rẹ pàdé, kì íse pé ó kàn ńsọ̀rọ̀ pé kó kàn rí kankan gbà nipasẹ̀ bóyá.

> *Ìwọ yóò yá ọ̀pọ̀lọpọ̀ orílẹ̀-èdè ṣùgbọ́n ìwọ kò ní í yá lọ́wọ́ ẹnìkankan.* OLÚWA *yóò fi ọ́ ṣe orí, ìwọ kì yóò sì jẹ́ ìrù. Bí o bá fi etí sílẹ̀ sí àṣẹ* OLÚWA *Ọlọ́run rẹ tí mo fi fún ọ kí o sì máa rọra tẹ̀lé wọn, ìwọ yóò máa wà lókè, bẹ́ẹ̀ ni ìwọ kì yóò wà ní ìsàlẹ̀ láé.*
>
> —Diutarọ́nọ́mì 28:12b-13

Nígbàtí Ọlọ́run bá ńsọ̀rọ̀ nípa bíbá gbogbo àìnim rẹ pàdé, Ohun tí ó ńsọ ni kí o wà ní ipò òmìnira pátápátá nípa ètò ìnáwó rẹ kí o wà láidjẹ gbèsè, máa rìn nínú àkànse isẹ́ rẹ pẹ̀lú ìfẹ́, àti kí o sì jẹ èyí tódára nínú èrè ilé nà. O tún túmọ̀ sípé o wà ní ìlera pípé àti ní àlááfià pípé.

Ẹlẹ́kejì, lẹ́yìn tí a ti bá àìní rẹ pàdé, kí íse pé o kàn wà láyè nìkan sùgbọ́n ò ńgbèerù,

> *Bẹ́ẹ̀ ni a sọyín di ọlọ́rọ̀ ninú ohun gbogbo, fún ìláwọ́ yín nínú ohungbogbo ní ọ̀nà gbogbo.*

Òpin gbogbo rẹ̀ ni láti ní agbára ti ìsúná fún inú rere, láti le fi fún àti ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́, àti láti sàtìlẹ́yìn fún àkànse iṣẹ́ Ọlọrun lórí ilẹ̀ ayé.

Erò Ọlọ́run ni láti mú kí ìfẹ́ ọkàn Rẹ̀ hàn sí àwọn ènìyàn àti láti darí ọkàn àwọn ènìyàn sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀.

Bí mo ti máa ńsọ ní gbogbo ìgba pé, "Ọlọ́run wà nínú oko-òwò àwọn ènìyàn."

Jẹ́ ki nfi àsìkò yí sọ̀rọ̀ lórí irọ́ tí àwọn ènìyàn rò ti mo máa sábà gbọ́.

Mo nbá ẹnìkan tí ó ní ọrọ̀ gan sọ̀rọ̀ ní ọjọ́ kan,Wọ́n wá sọ pé, "mi ò nílò owó sí i mọ́; Mo ti ní owó púpọ̀."

Níbáyìí, mo ti mọ ohun tí wọ́n ńgbìyànjú láti sọ—wọ́n ńsètọ́jú wọn dáda, pé wọn kò sì tún nílò owó kankan mọ́ fún ara wọn. Sùgbọ́n òtọ́ ibẹ̀ ni pé wọn nilò owó ati ọ̀pọ̀ púpọ̀ rẹ̀.

Tí a bá le wo ohun tí owó le se fún wa *tìkálárarẹ̀,* nígbàna mo ròó wípé àsìkò kan ńbọ̀ tí ńkan tí ó má mú kí á fẹ́ gba owó pípọ̀ le dínkù. Sùgbọ́n tí o ba ti mọ ọkàn Ọlọ́run láti jáde dé ọ̀dọ̀ àwọn ènìyàn àti dé ọ̀dọ̀ míllíọnù ènìyàn tí wọ́n ò tí sàwárí ìgbé ayé rere tí mbẹ nínú ìjọba Rẹ—tí wọn sì dorim kọ ibi gan tí à ńpè ní ọ̀run àpádì lọ́wọ́lọ́wọ́—nígbàna yóò yé ọ pé Ọlorun nílò ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó!!!!

Jẹ́ kín sọ ó lẹ́ẹ̀kansi, **ỌLỌ́RUN NÍLÒ OWÓ PÍPỌ̀ SII**

Ọpọ̀ iṣẹ́ ni ó tùn wà láti se.

> *Ọlọ́run le mú kí gbogbo ore-ọ̀fẹ́ wà ní àkúnwọ́sílẹ̀ fún wa, nínú ohungbogbo àti nígbàgbogbo, wà ni ohungbogbo tí o nílò, wa sì ní àkúnwọ́simlè nínú isé rere gbogbo.*

Oní isẹ́ rere gbogbo lati se. Isẹ́ rere gbogbo ni isẹ́ tí a se nítori tí Ọba. Kódà, o ní àwọn iṣẹ́ kan pàtó láti se, gẹ́gẹ́ bí Éfésù 4:7, 11-12a

> *Ṣùgbọ́n olúkúlùkù wa ni a fi oore-ọ̀fẹ́ fun gẹ́gẹ́ bi òṣùwọ̀n ẹ̀bùn Kristi. Nítorí náà ó sì ti fi àwọn kan fún ni bí aposteli; àti àwọn mìíràn bí i wòlíì; àti àwọn mìíràn bí efangelisti, àti àwọn mìíràn bí olùṣọ́-àgùntàn àti olùkọ́ni. fún àṣepé àwọn ènìyàn mímọ́ <u>fun iṣẹ́ ìránṣẹ́</u>.*
>
> —Efesu 4:7, 11-12a

Sé o ríi, ọ̀pọ̀ ènìyàn ni ó fẹ́ láti ní òmìnira nínú ètò ìsúná wọn nítorí egungun èkùrọ́ tí wọ́n lé ti sú wọn. Ní se ni wọ́n nwá àlááfíà. Nígbàtí ọ̀pọ̀ iṣẹ́ tí wọn ńse kò fojú hàn bẹ, wọ́n ńfojúsí òmìnira tí wọn yóò ní tí wọn bá

le ní owó. Wọ́n ńwá òmìnira láti se ohun tí wọn *fẹ́* láti se dípò ohun tí wọ́n bá *ní* láti se. Wọ́n fẹ́ láti tẹ̀lé ìfẹ́ ọkàn wọn àti mọ ìdí ohun tí ayé wọ́n ní láti ni i.

Gbólóhùn ọ̀rọ̀ yí máa mú kí àwọn ẹlẹ́sìn ènìyàn máa fẹ́ yawère:

*A sọ ọ́ di olọ́rọ̀ ní gbogbo ọ̀nà.*

Bẹ́ẹ̀ni, ó ti sọ bẹ. Pé a sọ ọ́ di ọlọ́rọ̀!

Níbáyìí nkan tí a pè ní ọrọ̀, lóotọ̀, ni a kò gboyé nínú àsa wa a kò tilẹ̀ le sọ pé ẹnikan tí ó ní bíllíọ́nù kan dọ̀lla ni inú rẹ̀ dùn ju ẹnití ó ní ọ̀kẹ́ máarún pọ́ùn lọ. Rárá lati jẹ́ "ọlọ́rò" ó túmọ̀ si àwọn nkan míràn sí onírúrú ènìyàn. Sùgbọ́n, lóòtọ́, ohun tí ó túmọ̀sí nipé gbogbo àìní wa ni a tí bá pàdé, tí a sì ńgbé ayé wa laíjẹ gbèsè àti máa jẹ̀gbádùn ilẹ̀ náà.

*Tí ẹ̀yin bá fẹ́, tí ẹ sì gbọ́rọ̀, ẹ̀yin yóò sì jẹ ojúlówó adùn ilẹ̀ náà.*
—Aísàyà 1:19

**NÍTORÍBẸ̀ LẸ́Ẹ̀KANSÍI, ỌLỌ́RUN FẸ́ KÍ O NÍ Ọ̀PỌ̀LỌ̀PỌ̀ ÌPÈSÈ LÁTI LE MÁA BÁ IṢẸ́ RẸ̀ LỌ NÍNÚ AYÉ.**

Láti jẹ́ ọlórò kì íse nípa níní owó lowọ́ nìkan. O níse pẹ̀lú bí bá àwọn ọmọ ọmọ ènìyàn seré, fí fa aya ẹni lọ́wọ́, àti àwọn ohun míràn tí ó tún dára nínú ayé. Emi àti Drenda ní àwọn ọmọ ọmọ márun tó dára, ti gbogbo wọn nífẹ́ Ọlọ́run ní ònà kan tàbí òmíràn tí àwọn náà ńbá wa se iṣẹ́ ìránsẹ́. Gbogbo wa súnmọ́ ara wa ajọ ńgbé papọ̀, má sì jẹ́ kíntàn ọ́ jẹ, a nífẹ sí láti má wà pẹ̀lú ara wa. Mo pèé ní jíjẹ́ ọlórò!.

Sé o rí, àwọn agbo ẹlẹ́sìn rò pé tí o bá ní owó pípọ̀ lọ́wọ́ ní ojúkòkòrò. Sùgbọ́n o kò le ní owó tó pọ̀jù tí o bá wà nínú oko-òwò ti ènìyàn pẹ̀lú Ọlọ́run. Gbogbo ìgbà ni iṣẹ́ àkànse àti àwọn agbègbè láti gbà.

Nítoríbẹ lẹ́ẹ̀kansii, Ọlọ́run fẹ́ kí o ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìpèsè láti le máa bá iṣẹ́ rẹ̀ lọ nínú ayé.

Ọlọ́run fẹ́ kí o jẹ́ onínúrere sí òn, kí o má ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́, àti kí o má se iṣẹ́ àkànse rẹ̀ gbogbo. Tí o bá fẹ́ jẹ́ onínúrere ní gbogbo ìgbà, o ní láti ní owó díẹ̀ lọ́wọ́.

Mo ńsọ pé, gbogbo ìgbà le jẹ́ *ojojúmọ́* tàbi *ní ìlọ́po ìgbà* ní ojọ́ kan. Jẹ́ kín sọ òótọ́ fún ọ—kí o tó le se èyí, kí ise owó ososù ni wà máa dúró dè:

wà ní láti ní ọpọ̀ owó lọ́wọ́ ju èyí tí ó nílò láti fi san iye owó tí o bá jẹ, o gbọdọ̀ jẹ́ owó tí ó pọ̀! Mo lérò pé gbogbo wa ni a gbà pẹ̀lú mi.

Jẹ́ki nwá fi ẹnu rẹ̀ sọ ibìkan nígbàtí a bá ńsọ̀rọ̀ nípa jíjẹ́ onínúrere tàbí nínú gbogbo ìfifúnni:

O ní láti bá ìbẹ̀rù wí nígbàtí o bá fẹ́ se ìfifúnni.

Mi ò sọ pé oní láti *yàgò* pẹ̀lú ìbẹ̀rù. Mo ní o ní láti BÁ ìbẹ̀rù WÍ nígbàtí o bá ńse ìfifún ni. Ọnà tí ó sì dára jùlọ láti fi bá ìbẹ̀rù wí ni pẹ̀lú òtítọ̀?

Bẹ́ẹ̀ kínni ìbẹ̀rù nínú ìfifúnni? Kí á kàn rọra sọ bẹ̀, pé a kò le rí ohun tótó fún ara wa, òótọ́?

*Mo nílò owó náà,* o le máa rò bẹ, àti pé lóotọ̀ o nílò rẹ̀. Sùgbọ́n Ọlọ́run na nílò rẹ̀ bákanna. Ọlọ́run kò sí ní bi ọ́ léèrè láti fún un ní owó rẹ láti lò láìse pé ó ti sèlérí pé òn máa san padà fún ọ, àti dá padà sórí ìdókòwò rẹ bí o ti sọ, On ni? Mo lérò pé ó sọ ọ́ ní àsoyé nínu ọ̀rọ̀ rẹ̀:

> *Ẹ fi fún ni, a ó sì fi fún yín; òṣùwọ̀n dáradára, àkìmọ́lẹ̀, àti àmìpọ̀, àkúnwọ́sílẹ̀, ni a ó wọ́n si àyà yín.*
>
> —Luku 6:38a

Ọlọrun fi ayè silẹ gan láti se àlàyé fún ọ àwọn ànfàní tí ó wà nínú síse àtiléyìn fún Ìjọba Rẹ̀ ju kí o sẹ̀sẹ̀ má sọ ohun tí wà se lọ. Ọ̀rọ̀ kan soso ni ó sọ, "*fi fún ni*" O sì lo àwọn ọ̀rọ̀ mẹ́tàlélógún láti se àlàyé *àwọn ànfàní* tí ó wà nínú rẹ̀ fún ọ. Mo lérò pé irú iṣẹ́ tí ó ni àdéhùn bẹ́ẹ̀ ni èmi máa fọwọ́sí!.

Kí o le mọ̀ pé Ọlọ́run ní inú dídùn sí kí o se dáradára. Ronú nípa rẹ̀:Níbo ni Ọlọrun ti fẹ́ rí owó tí ó nílò láti fi se ohun tí ó fẹ́ se?

Owó nà ní láti ti ọ̀dọ̀ rẹ jáde wá, àti èmi àti àwọn onígbàgbọ́ yókù, bẹ́ẹ̀ ni. Awọn ènìyàn Sàtánì kọ́ ni yóò se àkànse isẹ́ Ọlọ́run.

Ohun tí ó baninujẹ́ nipé ọ̀pọ̀ àwọn onígbàgbó ni yóò sọ pé kòbójúmu láti gba Ọlọ́run gbọ́ fún ìdápadà ìfifún ní wọ̀n. Ìgbàgbó wọn nipé tí ó bá fi fún Ọlọrun tí o tún wá ńretí ohunkóhun padà ó dàbí ojúkòkòrò ó sì tún le dín sínsin Ọlọrun ní ìwà mímọ́ kù.

Sé o gbàgbọ́ pé àgbẹ̀ kò mọ ohun tí ó ńse láti nígbàgbọ́ pé ìfifún ni rẹ̀ yóò mú èrè wam fún òun àti ìdílé rẹ? On lo ìlànà òfin ti Ọlọ́run fifún ni.

Ọlọ́run ní inú dídùn sí káserere. Ó fún wa ní òfin gbíngbìn àti kíkórè

fún ànfàní wa. Èsù ti paró fún ìjọ nípa ìfifún ni àti owó láti ìbẹ̀rẹ̀ wá. Awọn ìjọ kan wà tí wọ́n ńsògo nínú ẹ̀jẹ́ àìní wọn, laímọ̀ pé àwọn ńsubú tàarà sínú irọ́ pípa tí Sàtánì ni. Jésù ní lamti bá irú àwọn ìwà bẹ wí ní ọ̀pọ̀ ìgbà nínú isẹ́ ìránsẹ́ Rẹ̀. Kódà ó sọ ọ nínú ọ̀kan lára òwe tí ó sọ tó ní se pẹ̀lú ǹkan tí a ńsọ yìí, òwe ara Samáríà .

*Sì kíyèsi i amòfin kan dìde, ó ń dán an wò, ó ní, "Olùkọ́, kín ni èmi ó ṣe kí èmi lè jogún ìyè àìnípẹ̀kun?"*

*Ó sì bi í pé, "Kí ni a kọ sínú ìwé òfin? Báwo ni ìwọ sì ti kà á?"*

*Ó sì dáhùn wí pé, "'Kí ìwọ fi gbogbo àyà rẹ, àti gbogbo ọkàn rẹ, àti gbogbo agbára rẹ, àti gbogbo inú rẹ fẹ́ Olúwa Ọlọ́run rẹ'; àti, 'ẹnìkejì rẹ bí ara rẹ.'"*

*Ó sì wí fún un pé, "Ìwọ́ dáhùn rere. Ṣe èyí, ìwọ ó sì yè."*

*Ṣùgbọ́n ó ń fẹ́ láti da ara rẹ̀ láre, ó wí fún Jesu wí pé, "Ta ha sì ni ẹnìkejì mi?"*

*Jesu sì dáhùn ó wí pé, "Ọkùnrin kan ń ti Jerusalẹmu sọ̀kalẹ̀ lọ sí Jeriko, ó sì bọ́ sí ọwọ́ àwọn ọlọ́ṣà; wọ́n gbà á ní aṣọ, wọ́n sá a lọ́gbẹ́, wọ́n sì fi sílẹ̀ lọ ní àìpatán. Ní kòńgẹ́ àkókò yìí ni àlùfáà kan sì ń sọ̀kalẹ̀ lọ lọ́nà náà. Nígbà tí ó sì rí i ó kọjá lọ níhà kejì. Bẹ́ẹ̀ náà sì ni ọmọ Lefi kan pẹ̀lú, nígbà tí ó dé ibẹ̀, tí ó sì rí i, ó kọjá lọ níhà kejì. Ṣùgbọ́n ará Samaria kan, bí ó ti ń re àjò, ó dé ibi tí ó gbé wà; nígbà tí ó sì rí i, àánú ṣe é. Ó sì tọ̀ ọ́ lọ, ó sì di ọgbẹ́ rẹ̀, ó da òróró àti ọtí wáìnì sí i, ó sì gbé e lé orí kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ ti òun tìkára rẹ̀, ó sì mú un wá sí ilé èrò, a sì ń ṣe ìtọ́jú rẹ̀. Nígbà tí ó sì lọ ní ọjọ́ kejì, ó fi owó idẹ méjì fún olórí ilé èrò ó sì wí fún un pé, 'Máa tọ́jú rẹ̀; ohunkóhun tí ìwọ bá sì ná kún un, nígbà tí mo bá padà dé, èmi ó san án fún ọ.'"*

*"Nínú àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí, ta ni ìwọ rò pé ó jẹ́ ẹnìkejì ẹni tí ó bọ́ sí ọwọ́ àwọn ọlọ́ṣà?"*

*Ó sì dáhùn wí pé, "Ẹni tí ó ṣàánú fún un ni."*

*Jesu sì wí fún un pé, "Lọ, kí o ṣe bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́!"*

—Lúkù 10:25-37

Mo lérò pé gbogbo wa lati gbọ́ ìtàn yìí pẹ̀lú ẹ̀kọ́ tí ó kọ́ wa: Kín ni

Ọlọ́run kò bá se tí ó bá jẹ́ pé on ni ó nrìn lọ ní ojú ọ̀nà tí ó si rí ọkùnrin na? A mọ̀ pé Olúwa kò ní fi ọkùnrin tí wọ́n ti nà yí sílẹ̀ kó kú sí ojú ọ̀nà.

Ẹkọ́ tí ọ̀pọ̀ àwọn olùkọ ilé ọjó ìsinmi má ńkọ wa nínú ìtàn yíi ni pé kí á jẹ́ alábàágbélé rere. Má sètọ́jú àwọn ènìyàn. Síse ìtọ́jú àwọn ènìyàn jẹ ọkàn Ọlọ́run, mo sì le sọ pé mo fi gbogbo ara gba àgbéyẹ̀wò n. Síbẹ̀sìbẹ̀, ọ̀pọ̀ nkan ni ó wà níbẹ̀ tí a máa fi ìgbàgbogbo fojúfò.

Kí a tó le ní òye tòótọ nípa ìbáwí tí Jésù bá àwọn olùkọ òfin wí, ó ní láti oní láti ni òye ojú ọjó láwùjo Àwọn Juu ńkẹ́gàn àwọn ará Samáríà àti rí wọn bí alaímọ́ àti tí alaíbìkítà ohun ti ẹ̀mí. Bẹsìni, àwọn ará Juu rí ara wọn bí ẹni mímọ́ jùlọ àti olódodo ní iwájú Ọlọ́run ju àwọn ará Samárìa lọ dé ibi pé wọn kò fẹ́ ní ǹkan bá wọn se papò. Torí ìdí èyí ìtàn tí Jésu sọ jẹ́ àbùkù sí àwọn amòfin lójú wọn, àti ìbáwí sí ìwà ènìyàn burukú. Mo lérò pé gbogbo wa ní o ye.

Sùgbọ́n èyí tí mi ò tíi gbọ́, àní tí mi ò ti gbọ kí wọn kọ́ ní ilé ẹ̀kọ́ ọjọ́ ìsinmi ní ìtàn tí ó níse pẹ̀lú owó idẹ méjì. Kílódé tí Jésù se sọ̀rọ̀ nípa owó idẹ méjì tí ó bá jẹ́ pé kókó ohun tí ó fẹ́ sọ na ni nípa ọkàn àwọn olùkọ́ yi tí kò dára sí ará Samáríà? Jẹ́ kí a lọ wòó.

> *Ó sì gbé e lé orí kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ ti òun tìkára rẹ̀, ó sì mú un wá sí ilé èrò, a sì ń ṣe ìtọ́jú rẹ̀. Nígbà tí ó sì lọ ní ọjọ́ kejì, ó fi owó idẹ méjì fún olórí ilé èrò ó sì wí fún un pé, 'Máa tọ́jú rẹ̀; ohunkóhun tí ìwọ bá sì ná kún un, nígbà tí mo bá padà dé, èmi ó san án fún ọ.*
>
> —Lúkù 10:34a-35

Nínú ìtàn yí tí Jésù ńkọ́ wa, a tún le ri pé ó jẹ ara àpẹẹre ohun tí Jésù fẹ́ se fún wa. A le ríi bí Sàtánì ti fiyàjẹ àti pa ìran ọmọ ènìyàn lára, Sàtánì olè. Aní òye pé òróró àti wáínì jẹ́ ìsọtẹ́lẹ̀ tí ó dúró fún Ẹ̀mí Mímọ́ àti ẹ̀jẹ̀ ti Májẹ̀mú èyí tí Jésù yóò fi fún gbogbo àwọn tí ó bá tọ̀ọ́ wá. A sì ri nínú ìtàn na pé, lẹ́yìn na tí ó ti fi òróró àti wáìnì yán, ará Samáríà tún gbé ìgbésẹ̀ síwájú síi ó sì gbé ẹnití a palára yí lọ sí ilé èrò fún ìtójú. Ará Samàríà na mọ̀ pé arákùnrin yìí nílò àsìkò láti gba ìwòsàn, ó sìgbe lọ sim ibití om ti le gba ìtọ́jú, ó sì tún san gbogbo tí yóò na.

Mo gbàgbọ́ pé ilé èrò dúró gẹ́gẹm bí ìjọ agbègbè. Ibíyìí nà ni Jésù kó àwọn tí ati fiyàjẹ tí a palára ní ojú ọ̀nà ti ayé wá. Wọ́n ti di àtúnbí, a ti wẹ̀

wọ́nnù kúrod nínú ẹṣẹ̀ wọn nípa ẹ̀jẹ̀ májẹ̀mú tí ó wà láàyè nípasẹ̀ ti Ẹ̀mí mímọ, síbẹ̀ wọ́n tún ńgbé àbàwọ́n àti ìrora ègún ti ayé kiri. Wọ́n nílò àsìkò fún ìwòsàn àti láti kọ́ bí a ti se ńgbé ìgbé ayé titun. Jésù fi wọ́n sínú ìjọ agbègbè àti lábẹ́ olùsọ ilé èrò, Pásítọ̀ ìjọ agbègbè, láti máa bójútó wọn bí wọ́n ti se ńdàgbà.

Sùgbọ́n ó seni láànú, a tún rí irú àwọn ìwà yìí bákanna nínú ìjọ tí àwọn amòfin wà. Àwọn ènìyàn kò fẹ́ lọ́wo sí ríran ara ẹni lọ́wọ́ nínú ilé èrò. Bí àwọn tí ọ kọjá lọ lára ẹni tí wọ́n sálọ́gbẹ́, wọ́n rí ìsoro rẹ̀ bi ìsòro ti ẹlòmíràn. Kín wa ni ti àwọn láti dáasi? Kílósì wà níbẹ̀ ju kí ó gbà wọ́n ní àkókò àti kí ó ná wọn ní owó lo?

Nítorí irú àwọn ìwa yìí, àwọn pásítọ̀ má ńlo àsìkò wọn láti máa bẹ àwọn ènìyàn láti ràn wọ́n lọ́wọ́ ní ilé ìtọjú ọmọ-ọwọ́ tàbí láti bá wọn darì agbo kékeré. Sùgbọ́n ó wà dàbim ẹnipem àwọn ènìyàn kò ráye mọ́ láti farajidn nítorí isẹ́ tara wọn. Bẹ́ẹ̀ni ẹ̀sìn fúnrarẹ̀ kò fún wọn ní kóríyá mọ́, isẹ́ àti òfin nìkan ló wà. Ẹ̀sìn nà wam gbìyànjú láti da ẹ̀bi ru ènìyàn láti se ìrànwọ́ nípa sísọ pé, "O jẹ Ọlọ́run nígbèsè láti se èyí tabi tọ̀hún fún Un. Ati pe, o ye ki o wo ohun ti Olorun ti se fun o" Mo sì gbà bẹ, pé ó yẹ kí á máa ní ọkàn ìmore sí Ọlọ́run àti ní ìpinnu láti má ran àwọn ẹlòmíràn lọ́wọ́, sùgbọ́n Ọlọ́run kì ise bẹ́ẹ̀ pé nítorí tí "o jẹ mí nígbèsè" rárá. O ní èmi ó fi owó idẹ méjì fún olórí ilé èrò 'Máa tọ́jú rẹ̀; OHUNKÓHUN tí ìwọ bá sì ná kún un, nígbà tí mo bá padà dé,"

Lẹ́ẹ̀kansíi, ẹni tí ó ní ọkàn ẹ̀sìn yóò tún sọ pé gbólóhùn yí túmọ̀ sí pé tí a bá dé ọ̀run ni, ní Jésù yóò ti fi èrè isẹ́ gbogbo tí a ti se lórí ilẹ̀ ayé fún ìjọba Rẹ̀ fún wa. Rárá, nígbàtí Jésù ńsọ ìtàn na, Ó ńsọ *nípa* àwọn arìnrìn àjò ti ó lọ sòwò pé tí wọ́n ńbà padà bọ̀ wá láti ìrìn àjò won, Jésù ńsọ níti àkókò gan tí wọn se ìrànlọ́wọ́ fún àwọn olùsọ́ ilé èrò. Sùgbọ́n àwọn ènìyàn yóo sọ nísinsìnyí pé "nkan ńla ni" Ọlọ́run yóò fi gbogbo rẹ̀ fún olórí ilé èrò àti gbogbo ohun tí ó bam kù nígbàtí ó ńsetọjú ènìyàn naa, èmi pẹ̀lú ni àwọn ìnáwó tim mo fẹ́ se ní ilé mí. Mi ò le rí ayè tàbí owó láti fi sé e" irú àwọn ònà yí láti le mú kí àwọn ènìyàn dá sí ti Ọlọrun kò wú ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn lórí mọ́. Ó ní ohun tí ó ńse ọ, sùgbọ́n kò fi gbogbo ìtàn ìfẹ́ tí Ọlọrun hàn fún àwọn tí ó ńsé e.

Bẹ́ẹ̀ni mo mọ ohun tí wa sọ: "Gbogbo wa ní ó yé kí á se ìrànlọ́wọ́ nínú

ilé èrò nítorí ìfẹ́ tí a ní sí Ọlọ́run. "Bẹ́ẹ̀ni, o le sé nítorí tí ó jẹ́ olóòtọ́ sí Pásítọ̀ rẹ àti ìfẹ́ rẹ fún isẹ́ Ọlọ́run, tí o mọ̀ pé yóò gba nkankan…Sùgbọ́n Ọlọ́run fẹ́ kí o ní inú *dídùn* sí "isẹ́ nínu ilé èrò" pẹ̀lú Rẹ̀.

Bí o ti jẹ́ nìyí—a kò sisẹ́ FÚN Ọlọ́run sùgbọ́n, dípò bẹ, PẸ̀LÚ Ọlọ́run. Ọlọ́run, tìkararẹ̀ sọ àwọn nkan wọ̀nyií nípasẹ̀ Paúlù:

> *Ta ni ó ṣíṣẹ́ ológun tí ó sanwó ara rẹ̀? Ta ní gbin ọgbà àjàrà tí kì í jẹ nínú èso rẹ̀? Tàbí ta ní ń bọ ọ̀wọ́ ẹran tí kì í sí ì jẹ nínú wàrà ọ̀wọ́ ẹran? Èmi ha sọ nǹkan wọ̀nyí bí ènìyàn? Tàbí òfin kò wí bákan náà bì? Nítorí nínú òfin tí Ọlọ́run fún Mose, ni a tí kọ ọ́ pé, "Ìwọ kò gbọdọ̀ di màlúù ti ń tẹ ọkà lẹ́nu." Ǹjẹ́ màlúù ni Ọlọ́run n ṣe ìtọ́jú rẹ̀ bi? Dájúdájú ó sọ eléyìí fún wa pé, nítorí wa ni a ṣe kọ̀wé yìí kí ẹni tí ń tulẹ̀ lè máa tulẹ̀ ní ìrètí àti ẹni tí ń pakà lè ni ìrètí láti ní ìpín nínú ìkórè.*
>
> —1Kọ́ríntì 9:7-10

Ọlọ́run kò fe kí o ma sin Òn nínú ìbẹ̀ru tàbi nínú ojúse. Sàkìyèsí ohun tí ó sọ "*nítorí wa ni a ṣe kọ̀wé yìí kí ẹni tí ń tulẹ̀ lè máa tulẹ̀ ní ìrètí àti ẹni tí ń pakà lè ni ìrètí láti ní ìpín nínú ìkórè"* Ọlọ́run kò kàn fẹ́ ìkórè tí ńse èsì àbájáde ti isẹ tí ó ní lórí re nìkan. Ó tún fẹ́ ẹ́ fún àwọn tí o ńsiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú Rẹ, o sì fẹ́ kí gbogbo wọ́n pín nínú ayọ̀ ìkórè na bí ó ti ńse.

Jésù yan olórí ilé èrò fún ìtàn na fún idí tó se pàtàkì ni. A mọ̀ pé olórí ilé èrò ńsòwò ni. Ó ti gbé iye tí yóò ma pa lójúmọ́ lé orí iṣẹ́ àti àwọn òsìṣẹ́ rẹ̀. Sùgbọ́n ju gbogbo re lọ o sì nílò owó tí yóò ma fi sisẹ́ nínú ilé èrò, kí èrè rẹ̀ le pòsi. Ó dára bẹ, *ere* .

Nígbogbo ìgbà tí olórí ilé èrò bá ti díyelé àwọn àlejò rẹ̀ tí wọn sùn mọ́jú, ní ó ńjèrè. Nìtorí idí èyí, ọ̀tọ̀ ni ojú tí olórí ilem èrò fi wo ọkùnrin tí wọ́n gbé wá bá a yií. Kò na ní kóbọ̀ láti sètọjú rẹ̀, níwọ̀n ìgbàtí arìnrìnàjo náà ti sèléri láti san gbogbo iye tí ó bá ná lórí rẹ̀. Sùgbọ́n olórí ilé èrò mọ idí tí ó fi gbà láti se ìrànwọ́ fún okùnrin na laísàríyànjiyàn. Kó dà, ó fẹ́ẹ̀ le má jóyípo lórí irú ànfàní tí ó bá ara rẹ̀.

Só rí i, olórí ilé èrò mọ̀ pé ní alẹ ọjó kọ̀kan tí arakùnrin yìí bá ti sùn ni òun yóò jèrè tiẹ̀, pẹ̀lú ohun tí arìnrìn àjò ti sọ fún pé òun ó san gbogbo ohun tí ó bá ná fún ìtọ́jú, ó ńsọpé. Mo fojú inú wo nkan tí olórí ilé èrò àti

ọkùnrin onísòwò le jọ máa sọ bí ó ti nlọ sí ìrìn àjò rẹ;" Ha, tí o bá rí ẹlòmíradn tí ó nílò ìránlọ́wọ́ ní ojú ọ̀nà, jọ̀wọ́ rídájú pé ó gbé wọn wá síbí. Gbogbo ohun tí o bá le gbé fún mi wa ni màá gbà, tí yàrá kò bá tó màá tumn wá yàrá síi!

**Ó BANÍLỌ́KÀN JẸ́ PÉ WỌ́N PÀDÁNÙ ỌKÀN ỌLỌ́RUN, TÍ Ó FẸ́ FI TỌKÀNTỌKÀN SAN OHÚNKÓHUN TÍ Ó BÁ NÁ WỌN LÁTI DÉ ỌDỌ̀ ÀWỌN ÈNÌYÀN, TÍ Ó SÌ MAA NSÁN FÚN WA NÍGBÀ GBOGBO JU OHUN TÍ A NÁ LỌ. NÍGBÀ GBOGBO.**

Bí ìwọ na ti se rí pé, ọ̀pọ̀ nkan tí ó wà nínú rẹ pọ̀ju ìtàn kín ni ohun tí Jésù yóò se tí gbogbo wá mọ̀ bim ẹni mo wó lọ. Jésud ńgbìyànjú láti tún èrò ọkàn àwọn ẹlẹ́sìn tí wọ́n jẹ́ ọmọ̀ràn nínú òfin tí wọn ní sí Ọlọ́run àti ara Samáríà. Ó sì tún jẹ́ kí ó mọ̀ pé ó ti pàdánù ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ànfàní ńlá tí ara Samáríà ti rí gbà—*èrè!*

Gbogbo ìgbà tí mo bá gbọ́ tí àwọn ènìyàn ńsọ wípé Ọlọ́run se nkan tí kò dára sí àwọn ènìyàn rere,ní ọkàn mi má ńbàjẹ́ tàbí rí àwọn ẹni tí ń sin Ọlọ́run nínú ojúse ti ìgbàgbọ́, dípò ìgbésí aláyọ̀ tí ó yẹ kí wọ́n máa gbé. Sàtánì ti gbìyànjú láti fi ojúrere Ọlọrun pamọ fún àwọn ènìyàn Ọlọ́run kí wọn má ba fi tọkàntọkàn sìn Ín pẹ̀lụ́ gbogbo ọkàn wọn.

Sí áwọn ènìyàn kan ìjọ Ọlọ́run dàbí ibití ìsẹ̀lẹ̀ kan tún tí sẹlẹ̀, dípò kí wọ́n ní òye pé àwọn gan ni ìjọ, ilé èrò ti Ọlọ́run rán àwọn ènìyadn lọ láti jẹ́ mímọ́. Ó banilọ́kànjẹ́ pé wọ́n pàdánù ọkàn Ọlọ́run, tí ó fẹ́ fi tọkàntọkàn san ohunkóhun tí ó bá ná wọn láti dé ọ̀dọ̀ àwọn ènìyàn, tí ó sì máa nsán fún wa nígbàgbogbo ju ohun tí a ná lọ nígbà gbogbo.

Mo sì le rántí ní ọjọ́ tí èmi àti brọdà Drenda jọ jóòkó bí ọdún díẹ̀ sẹyìn tí a njíròrò lórí kókó ọ̀rọ̀ yìí kanna—pé Ọlọ́run dára òun sì olùsẹ̀san, ó sì ti fi ìjọba tí yóò bá gbogbo àìní wa pàdé fún wa. Òye ìjọba yìí sí jẹ́ ohun titun sí Johnny ati ìyàwom rẹd, Candi, bí wọ́n ti kúrò nínú ìjọ ìbílẹ̀ níbití wọn ti ńkọ́ wọn àti sọ òtító níwọ̀nba fún wọn.

Johanny ati Candi ńsisẹ olùkó ní ilé ìwé Georgia ní àsìkò na, bí wọn sì ti ńsisẹ olùkọ wọn lo, ni Johanny tún sisẹ́ pẹ̀lú ilé iṣẹ́ ti Ìsúná mi, fún apákan àkókò rẹ̀ Forward Finanancial Group. Ó dàbí pé Johnny mọ̀ nípa oko-òwò síse. Ní ọdún àkọ́kọ́ re pẹ̀lú ile iṣẹ nà, ó ní àseyọrí gan nínú

apákan àkókò ju ohun tí ó se ní ọdún kan nínú isẹ́ olùkọ́ni tí ó ńse lọ, nítorí ìdí èyí ó pinnú láti fi isẹ́ olùkóni sílẹ̀ láti máa se isẹ́ ti ilé isẹ́ oko-òwò Ìsúná. Ní ìbẹ̀rẹ̀ Johanny ńse dáada. Sùgbọ́n nígbàtí ó ya, mo ri wípem ohun gbogbo tí ó ńse ni ó ti bẹ̀rẹ̀ sí ní falẹ̀, mo sì rò pé kò ní le máa bá lọ bẹ́ẹ̀ fún ìgbà pípẹ́.

Èmi adti Drenda ti ńsètò ìrìn àjò lọ sí Georgia fún àkókò ọdún kérésìmesì, mo sì ńgbàálérò láti dúró àti lo àsìkò díẹ̀ pẹ̀lú Johanny láti rí bóyá mo le mọ àwon ìdí kan tí ó fà tí kò fi se dáada mọ́ nínú oko-òwò tí ó nílò láti máa se. Kódà, kín tó pe Johnny, ni òun tìkararẹ ti pè mí láti bèrè pé bóyá ma tẹ̀sẹ̀ dúró ní ọ̀dọ̀ òun kí a bá le jọ jíròrò lóri isẹ́ nàa. Bẹ sì ni mo ti setán láti se bẹ́ẹ̀.

Mo fẹ́ sọ fún ọ pé ẹ̀rù tí ńba Johnny àti Candi. Nítorí wọn ti ní ẹdẹ̀gbàta pọ́ùn nílẹ̀ tí ó yẹ kí wọ́n ti san nínú osù tí wọn wà lọ́wọ́lọ́wọ́, tí wọn kò sì ní ibití owó kan ti má wọle fún wọn fún ẹdẹ̀gbàta pọ́un míràn tí wọn ó tún san fún osù tí mbọ̀. Bi mó ti jokòo tán pẹ̀lú Johanny,àwọn ọ̀rọ̀ tí ó kọ́kọ́ sọ ni "kò ti lẹ̀ sisẹ́" Mo mọ̀ pé òye ti Ìjọba jẹ́ ohun titun sí Johanny ati Candi, mo rí pé ó yẹ kín kọ́ wọn bí wọn ti se le se nkan tẹ̀mí. Nítorípé mo mọ̀ pé Ìjọba má ńsisẹ́ nígbàgbogbo! Toríbẹ̀, mo lo bíi wákàtí mejì pẹ̀lú wọn láti fi máa sàlàyé ìlànà òfin tí Ìjọba àti bí wọn ti se le máa lo ìgbàgbọ wọn. Bí mo ti nsọ̀rọ̀ mo rí pe ìbẹ̀rù tú ńlọ àti ìgbàgbọ́ bẹ̀rẹ̀ sí ní dìde nínú wọn. Mo sì mọ̀ pé Johnny ti setán fún ìpele tókàn.

Mo ni "Johnny" o ní láti fi irúgbìn fún Ọlọ́run kí o sì gbà á gbọ́ fún gbogbo owó tí o nílò."

Johnny àti Candi sí gbà pẹ̀lú mi, sùgbọ́n wọn kò ní owó kankan. Ó kàn sẹlẹ̀ bẹ́ẹ̀ pé èmi ti mú owó tí wọn yóo fi san owó ọ́fisì tí wọ́n ńlò dání láti ilé tí ńse ọgọ́jọ pọ́ùn. Mo mọ̀ pé wọn le lo owó nà, sùgbọ́n mo gbà wọn níyànjú pé kí wọn fi owó nàa fún Ọlọ́run bí írúgbìn nítorí tí a mọ̀ pé ọgọ́fà pọ́ùn na kò le tó láti san ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta pọ́ùn iye owó tí ó yẹ kí wọ́n san tàbí ẹ̀ẹ́dẹ̀gbàta èyí tí ó tún bọ̀ tí wọn ó san. Wọ́n sì gbà bẹ́ẹ̀.

Bí a ti fẹ́ láti gbàdúrà àti so ìgbàgbọ́ wa papọ̀, mo bèrè lọ́wọ́ Johanny pé kí ni ó ńgbàgbọ́ bí o ti ńfúrúgbìn èso owó yìí? Bí mo ti sọ̀rọ̀ tán, ni Ẹ̀mi Mímọ́ sọ fún mi pé kí má jẹ́ kí o fún ọ lésì, mo sì mọ idí. Johnny kò bá dáhùn pé òun ní ìgbàgbọ́ pé ẹ̀ẹ́dẹ̀gbàta pọ́ùn yóò jẹ́ sísan, nítorí pé ibití

ìsòro rẹ̀ wà na nìyìí. Ẹ̀mí Mímọ́ wá sọ fún mi láti "bí léèrè pé sé ẹgbààfà pọ̀ùn yóò tó ó fún ọgbọ̀njọ́." Toríbẹ̀, nkan tí mo sọ na nìyí, mi ò jẹ́ kí ó fèsì, mo nì sé ẹgbààfà pọ̀ùn máa tó ọ ná ní ọgbọ̀njọ́. Mo rí tí ojú rẹ̀ là wà bí mo ti sọ iye owó tí Olúwa sọ fún mi láti bèèrè lọ́wọ́ rè. Mo mọ̀ pé Johnny kò tí I gba irú owó tótó ẹgbààfà pọ̀ùn rí ní àrin ọgbọ̀njọ́ ní gbogbo ọjọ́ ayé rẹ̀. Ó jókòó sí bẹ̀ fún bí ìsẹ́jú kan ó wá dáhùn pé, bẹ́ẹ̀ni, ohun yóò gbàgbọ́ pẹ̀lú mi. Mo wá bi Candi ní ìbéèrè yìí kanna, òun na ní bẹ́ẹ̀ni. A sọ ọwọ́ wa papọ̀ a gbéelé ori sọ̀wédowó nà, a sì sọ̀rọ̀ ìgbàgbó wa jáde fún ẹgbààfà pọ̀ùn ní ososù.

Lẹ́yìn ọ̀sẹ̀ kẹta, Johanny pè mí. Inú rẹ̀ dùn gan. Ó ti ko ọ̀pọ̀ isé ní àrin ọ̀sẹ̀ mẹ́ta sẹ́yìn tí yóò fun ní  iye owó tí kì íse e ẹgbààfà pọ̀ùn ni bíkòse ẹẹ̀dẹ̀gbàsán pọ̀ùn. Ó ní ó sẹ̀ṣẹ̀ mọ̀ pé onígbàgbọ́ ni òun báyìí.

Ní bí osú méjì sẹ́yìn ni ìjànú ọkọ̀ Johnny sẹ̀ sẹ lẹ̀ ní alẹ́ ọjọ́ kan tí òjò ńrọ̀ nígbàtí o nlọ sí ilé lẹ́yìn ìpàdé tí ó lọ se. Tí ọkọ̀ ná sí bàjẹ́ kọjá àtúnse, sùgbọ́n Johnny forítìí ní àsìkò na, tí òun gan sí mọ̀ pé Ọlọ́run ni ó seé. Síbẹ̀, ńitorí ìjàmbá ọkọ̀ nà, Johnny kò ráyè sisẹ́ bó ti yẹ, kí o le padà bọ̀ sí pò ní àsìkò yí gan, àdéhùn àti san owó lórí ilé rẹ̀ tó tí àwọn afipá gbalé tún ti setán láti ta ilé rẹ̀. ó ṡi nílò ẹgbàárún pọ̀ùn láti má jẹ́ kí wọ́n ta ilé nà.

Àsìkò yìí gan ni Johnny ati Candi ti ńwo pé àwọn yóò kọjá lọ sí Ohio kí àwọn ba le súnmọ́ ibití àwọn ti máa gbọ́ ìdánílẹ́kọ̀ tó kún nípa Ìjọba tí ó le yí ayé àwọn padà. Toríbẹ̀, wọ́n fẹ́ gbé ilé wọn kalẹ̀ fún ẹni tí yóò yáa fún ìgbà díẹ̀. Bí wọ́n ti è mọ̀ pé àwon kò ní ju osù kan lọ mó nínú ilé nà kí àwọn alásẹ̀ tó wá ta ilé wọn.

Bí ọjọ́ ti ń súnmọ́ kò sí ẹníkan tí ó wá títí ó fi ku bí ọjọ́ melo sí ìgbànà ni ọkùnrin kan bá wá ó ní òun yóò ra ilé nà, sùgbón ó bèrè fún ànfàní. Ó fẹ́ mọ̀ bóyá òun le san ẹ̀ẹgbaàrún pọ̀ùn ná níbáyìí, kí wọn sì dúró nínú ilé nà fún ọgbòn ọjọ́ títí òun yóò fi wá láti san tán torí òun ni àwọn ọjà kan tí òun fẹ́ tà láti fi ra ilé nà.

Ó ya Johnny lẹ́nu. Ó mọ̀ pé tí òun bá fẹ láti gba ilé nà padà lọ́wọ́ àwọn agbélétà na, ó ní láti ní owó tí yóò san lọ́wọ́ ní tí ó sì ku bí ọjọ́ melo kan. Ẹnití ó fẹ́ ra ilé ti setán láti kọ sòwédowó fún Johnny eẹ̀gbàárún pọ̀ùn lójú ẹsẹ̀ àti san owó yokù tí ó bá ti yáa. Iye owó tí Johnny nílò gan sì nìyìí. Johnny mọ̀ pé Ọlọ́run ni, ó gba ẹ̀ẹgbàárun pọ̀ùn sọ̀wédowó, ó sì lọ san

owó ilé sin a lọwọ́lọ́wọ́. Ha, ẹ̀ẹ̀gbàárún pọ́ùn ni iye owó *tí ó wà lórí* ile nà.

Johnny àti Candi kọjá lọ sí Ohio wọ́n kó lọ sí ilé tí wọn yá gbé. Wọn sì lọ darapọ mó Faith Life Church, Johnny sí bẹ̀rẹ̀ sí ní se oko-òwò ti ètò isúná pẹ̀lụ agbára ọ̀tun. Sùgbọ́n ní báyiì ìsòro ọtọ̀ ni wọn tún ni. Ọkọ ẹyọkan ní wọ́n ní báyìí, tí Johnny sì nílò rẹ̀ láti má gbée kiri fún àwọn ìpàdé tí ó bá ti ní láàrin ọ̀sẹ̀. Wón tún fi èso irúgbìn fún ọkọ̀ titun wọ́n sì ní ìgbàgbọ́ pé àwon yóò rí gbà tí àwọn bá ti gbàdúrà, gẹ́gẹ́ bí Máàkù 11:24 ti so.

Nkan tí ó yànílẹ́nu kan wá sẹlẹ̀. Ọ̀rẹ́ àti gbàkékere Johnny wá pe…

"Johnny, ǹjẹ́ mo ti ẹ san owó kẹ̀kẹ́ tí o fún mi nígbàtí a wà ní ilé ẹ̀kọ́ onípele kẹfà? O bíi léérè.

"Rárá" ní Johnny sọ.

Nígbàna ní ọ̀rẹ́ rẹ̀ sọ pé, "ó dà, mà san án padà fún ọ nísisìyìí. Màá ra BMW kan fún ọ."

Nígbàtí wọn wà ní omodé, àwọn mejejì má sáàbà sọ̀rọ̀ nípa ọkọ̀ ó sì mọ̀ pé Johnny nífẹ sí BMW gan. Ọ̀rẹ́ rẹ̀ yí sì jẹ́ olótítọ́ sí ọ̀rọ̀ rẹ̀ ó sì fi owó tí yóò fi ra BMW ránsẹ́ sí Johnny láti lọ ràá fún ara rẹ̀. Níkete tí owó dé ọwọ́ Johnny, ó mọ̀ pé pẹ̀lú bí ẹbí àwọn ti tó, kì ise BMW ni àwọn nílò. Oun ati Candi pinnu lati ra SUV tí yóò gba àwọn ẹbí wọn fún Candi àti ọkọ̀ kékeré kan fún Johnny láti má fi se isẹ́ tìrẹ nítorí ọkọ̀ kékeré tí Candi tí wọ́n ńlò tẹ́lẹ̀ ti gbó àti pé ó ti nyọwọ́. Toríbẹ nkan tí wọn se nìyìì.

Mo le rántí alẹ́ ọjọ́ tí Johnny pè mí. Ó jókòó nínú SVU rẹ̀ titun ní ojú ọ̀nà tí ńgbé ọkọ̀ rẹ̀ sí ní ẹ̀gbẹ́ ọkọ̀ rẹ̀ kejì pẹ̀lú omije lójú rẹ̀ bí o ti ńsàlàyé fún mi bí ó ti se ra ọkọ̀ mejì papọ̀ fún ìgbà àkọ́kọ́ nínú ayé rẹ̀.

Johnny jẹ́ ẹni tó sẹ̀sẹ̀ wá. Ó sì mọ̀ pé Ọlọ́run le se ohun gbogbo.

Ní ọjọ́ kan ó wá sí ọ́físì mi ó wá sọ fún mi pé ilé yíyá gbé ti sú òun, pé òun àti Candi fẹ́ ilé àti dáko àwọn sì ti ńwá. Ó da, Mo sì mọ̀ pé gbèsè tí Johnny jẹ̀ kò tí tán bẹ́ yẹn mó sì wá ńgbàníyànjú kí o ní sùúrù díẹ̀ si ní ibití ó ńyá gbé títí yóò fi kówójọ láti fí ayè sílẹ̀ kí gbèsè tó san. Sùgbọ̀n ó dàbí pé Johnny kò fiyèsí nkan tí mò ńsọ.

Ó wá sọ fún mi pé òun tí rí ilẹ̀ oko kan ní ìsàlẹ̀ ọ̀dọ̀ mí tí wọn fẹ̀ ta, òun sì fẹ̀ lo. wòó láti ràá. Lóòtọ, nítorí mo ti ní ile isẹ̀ ayánílówó sòwò rí, èmí mọ̀ pé kò sim ọ̀nà tim Johnny se le fi le yege lamti gba oko nà. Mo sì tún mọ̀ pé kó ní owó nílẹ̀ tí o le fi ra irú nkan bẹ.

Ó yàmílẹ́nu lẹ́yìn ọ̀sẹ̀ kan tí ó tún wá sí ọ́fisi mi pẹ̀lú ẹ̀rín láti sọ fún mi pé ilẹ̀ oko na ti di tirẹ̀. Nígbàtí ó sọ fún mi bẹ́, mo mọ̀ pé ìtàn tí mo fẹ́ gbọ nìyìí. Bẹ́ẹ́ni, òun ati Candi ti fún irúgbìn sí isẹ́ Ọlọ́run bí wọn ti se kọ́ wọn láti ní ìgbàgbó pé wọ́n ti rí gbà nígbàtí wọn bá gbàdúrà. Johnny tẹ̀síwájú láti sàlàyé nkan tí ó sẹlè fún mi.

Ó lọ sí bánkì rẹ nípa àti ra ilẹ oko na, ọ̀gá báńkì na si pé jókòo ó sọ fún pé Johnny o mò ohun tí gbèsè rẹ̀ jẹ́, o kò yege tó láti ra ohunkohun báyìí"

Sùgbòn ọ̀gá nà wá sọ ohun kan tó se àjèjì sí mi. Ó gbé ìwé gbèsè sí ẹ̀gbẹ́ kan ó wá sọ pé Sùgbọ́n mo fẹ́ràn rẹ. Jẹ́ kí nwo ohun tí mo le se síi"

Kín má fa ọ̀rọ̀ gùn, àwọn bánki ni ó san ìdá ọgọ́run bí mo ti se ra ilẹ̀ oko na, wọn sid fún ní osù mẹrin títí àsìkò tí wọn fi yáa lò yóò fi parí fún láti kó sí bẹ̀, ó ra epo si tánki, ó san gbèsè owó-orí tí ó ti wà nílẹ̀, ó fún Johnny ní ẹ̀ẹ̀dẹ́gbàta pọ́ùn láti fi se àtúnse ibi tí ó ti fọ́ níwájú ilé nà.

Mo jókoo sìbè pẹ̀lú ìyàlẹ́nu bí Johnny ti ńsọdrọ̀ rẹ̀ lọ nípa Ìjọba. "wow" nìkan ni ohun tí mo le sọ.

Lẹ́yìn osù kan sim ìgbàna, Johnny sọ fún mí pé òun tún ti fúrúgbìn fún katakata ti wọn fí ńdáko Ford. Ó sọ fún mí pé òun tí nílò katakata na ní oko òun àti fúrúgbín fún katakata Ford tí ń lo búlù diesel. Lẹ̀ẹ̀kansii, níwọ̀n ìgbàtí o tí ńsisẹ̀ fún mi, àti mọ iye tí owó katakata ńsọ, mo mò pé kò ti ní irú owó nà lọ́wọ́.

Sùgbọ́n sí ìyàlẹ́nu,ọ̀sẹ̀ díẹ̀ sí ìgbàna bí mo ti nwo ojú ọ̀nà, ní mo rí Johnny tí o ńwa ọkọ̀ Ford katakata búlud lọ sí ọ̀nà ilé rè. Nígbàtí mo bi léèrè pé níbo àti báwo ni ó ti se rí katakata na, ó sọ pé obinrin kan mọ̀ ọ́n mọ̀ wá sí ọ̀dọ̀ rẹ̀ ní ilé ìjọ́sìn ní ọjó nà ó sì bi léèrè pé sé ó mọ ẹnikẹ́ni tí ó nílò katakata. Wọ́n fẹ́ láti lukudétì oko àwọn òbí rẹ̀, katakata yìí sì wà níbẹ̀ tí wọ́n fẹ́ tà Johnny sọ fún pé òun nífẹ sí i.

Ó da, ó ní kí ó má se yọnu nípa àti san owó fún òun báyií, o le san án nígbàtí o bá ti ríi, kò kánjú rara. Bó se di ẹnití ó ní katakata nìyìí.

Àseyọrí rẹ̀ sí ńtẹ̀síwájú. Ní osù tó tún tẹ̀le, ó rí ẹgbàá-lé-ní-ọ̀kẹ́- mẹ́ta-àbọ̀ pọ́ùn ní àarìn osù kan. Tí ó bá bi Johnny léèrè pé báwo ni o ti se sẹlẹ̀, yóò sọ fún ọ pé ó sẹlè bẹ́ẹ̀ nítorí òun fifùn Ọlọ́run àti ní òye ìlànà òfin ti Ìjọba ni.

Ẹ wo irú ìtàn yíi! Mo sì tún le rántí ìgbà tí mo jókòó pẹ̀lú Johnny àti

Candi ní ilé wọn ní Georgia ní alẹ́ ọjọ́ nà tí mo pín nípa Ìjoba pẹ̀lú wọn. Bí ìrẹ̀wẹ̀sì tí mú wọn nítoríti wọn ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta pọ̀ùn tí wọ́n fẹ́ san gbèsè rẹ àti ẹ̀ẹ́dẹ̀gbàta míràn tí wọ́n tún retí, tí ó tún jẹ́ àkóko kérésìmesì tí kò sì *sí owo* kankan lọ́wọ́ wọn. Mo lérò wípé yóò wu ìwọ na láti gbó ohun tí mo bá wọn sọ ní alẹ́ ọjó nà.

Mo kàn mọ̀…pé mo ní láti jẹ́ ki mọ ẹnití Ọlọ́run ńse ní àkókò ti wọn ńdojú kọ àyídáyidà wọ̀nyíi. Mo wá bẹ̀rẹ̀ sí ní fi hàn wọ́n ohun tí iwe 2 Kọ́ríntì 9:10-11:

> *Ǹjẹ́ ẹni tí ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ, yóò fi irúgbìn fún un yín, yóò sì sọ ọ́ di púpọ̀, yóò sì mú èso òdodo yín bí sí i. Bẹ́ẹ̀ ni a ó sọ yín di ọlọ́rọ̀ nínú ohun gbogbo, fún ìlawọ́ yín gbogbo tí ń ṣiṣẹ́ ọpẹ́ sí Ọlọ́run nípa wa*.

Mo fi yé wa´pe Paúlù sọ pé Ọlọ́run kò ní pèsè irúgbìn tó gbìn nìkan sùgbọ́n yóò tún pèsè àkarà fún àiní rẹ. Àkàrà ńtọ́kasí ohun gbogbo tí ó nílò fún ìgbésí ayé rẹ. Láti inú rè, yóò mú kí agbára rẹ tún pọ̀si làti le fifunni síi. Ó túmọ̀sí pé wà máa pọsi.

Lẹ̀ẹ̀kansi, Kín ni ìbẹ̀rù tó wà nínú ìfi fúnni? Nípé wà máa dínà mọ́ àwọn ohun tí ó nílò.

Sùgbọ́n tẹ́tí sí ohnu tí Ọlọ́run bá sọ. Ó fi irúgbìn fún afúnrúgbìn àti àkàrà fún óunjẹ. Ìbéèrè pàtàkì kan nìyií, ìbéèrè tí mo sì bi Johnny nà nìyií.

**Sé ohun tí ó wà ní ọwọ́ rẹ ni irúgbìn tàbí óunjẹ? Ọwọ́ rẹ lówà.**

Bàbá mọ̀mọ́ mi, àgbẹ̀ ni bàbá mi àgbà, ńse ní gbogbo ọjọ́ ayé wọn. Mo sì rántí gẹ́gẹ́ bí ọ̀dọ́mọdékùnrin tí mo má nseré nínú kẹ̀kẹ́ ẹrù irúgbìn wọn. O le má gbọ́ nípa kẹ̀kẹ́ ẹrù irúgbìn rí. Ó le má sì jẹ́ nkan tí wón ńpe ni, sùgbọ́n ohun ti àwa má ńpe nìyií bí a ti ńdàgbà pẹ̀lú bàbá mọ̀mọ́ mi. Sé o wá ríi, nígbogbo ọdún ní àsìkò ìkórè, bàbá àgbà má ńfi ọ̀pọ̀ irúgbìn pamọ́ sínu kẹ̀kẹ́ ẹrù tí ó wà nínú àbá. Kẹ̀kẹ̀ ẹrud yí máa kún fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn irúgbìn èso tí wọn yóò tún gbìn ní ọdún tí ó mbọ̀.

Nínú àwọn osù ìgbà otútù, bàbá àgbad má ńri wípé kẹ̀kẹ́ ẹrù ńlá yìí kún dẹ́nu fún ẹ̀wàsoya, nítori wọn mọ̀ wípé àwọn le tètè rí tà nígbàtí àwọn bá nílò rẹ̀ tàbí kí wọn kó pamọ́ di ìgbà àti gbin fún ìkórè ńlá. Ọwọ́

wọn lówà láti yàn, sùgbọ́n wọn mọ̀ dájú nípa òfin ti ìgbà gbíngbìn àti ìkórè, ó sì gbé ìgbé ayé rẹ̀ lé wọn lórí.

Johnny ati Candi nà ní láti se ìpinnu nígbàti wọn mú sọ̀wédowó ọgọ́fà pọ̀ùn na dání. Wọ́n mọ̀ pé àwọn kò bá lò ó láti fi san owó tí wọn jẹ, sùgbọn dípò bẹ, wọn mọ̀ pé bí àwọn bá fifún Ọlọ́run ní owó nà yóò fún àwọn nim ìkóre tí ó ga laípẹ. Òtítọ̀ ni wón sì ńsọ.

*Ènìyàn kan ń fún ni lọ́fẹ̀ẹ́, síbẹ̀ ó ń ní sí i;òmíràn ń háwọ̀ ju bí ó ti yẹ ṣùgbọ́n ó di aláìní.*

—Ìwé Òwe 11:24

Kí á tó kúrò ní orí Bíbélì yìí, òwe kan tún wà tí mo fẹ̀ kí á tún gbé yèwò—Máátíù 25:14-30, òwe tálẹ̀ǹtì.

*A sì tún fi ìjọba ọ̀run wé ọkùnrin kan tí ó ń lọ sí ìrìnàjò. Ó pe àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀, ó sì kó ohun ìní rẹ̀ fún wọn. Ó fún ọ̀kan ni tálẹ̀ǹtì márùn-ún, ó fún èkejì ni tálẹ́ǹtì méjì, ó sì fún ẹ̀kẹta ni tálẹ̀ǹtì kan, ó fún olúkúlùkù gẹ́gẹ́ bí agbára rẹ̀ ti mọ, ó sì lọ ìrìnàjò tirẹ̀. Ọkùnrin tí ó gba tálẹ̀ǹtì márùn-ún bẹ̀rẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ láti fi owó náà ṣòwò. Láìpẹ́, ó sì jèrè márùn-ún mìíràn. Ọkùnrin tí ó gba tálẹ̀ǹtì méjì náà fi tirẹ̀ ṣòwò. Láìpẹ́, ó sì jèrè tálẹ́ǹtì méjì mìíràn. Ṣùgbọ́n ọkùnrin tí ò gba tálẹ̀ǹtì kan, ó wa ihò ní ilẹ̀, ó sì bo owó ọ̀gá mọ́ ibẹ̀.*

*"Lẹ́yìn ọjọ́ pípẹ́, olúwa àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ dé láti àjò rẹ̀. Ó pè wọ́n jọ láti bá wọn ṣírò owó rẹ̀. Ọkùnrin tí ó gba tálẹ̀ǹtì márùn-ún, mú márùn-ún mìíràn padà wá, ó wí pé, 'olúwa, ìwọ ti fi tálẹ́ǹtì márùn-ún fún mi, mo sì ti jèrè márùn-ún mìíràn pẹ̀lú rẹ̀.'*

*"Olúwa rẹ̀ wí fún un pé, 'O ṣeun ìwọ ọmọ ọ̀dọ̀ rere àti olóòtítọ́: ìwọ ṣe olóòtítọ̀ nínú ohun díẹ̀, èmi yóò fi ọ́ ṣe olórí ohun púpọ̀, bọ́ sínú ayọ̀ olúwa rẹ."*

*"Èyí tí ó gba tálẹ̀ǹtì méjì wí pé 'Olúwa, ìwọ fún mi ní tálẹ́ǹtì méjì láti lò, èmi sì ti jèrè tálẹ́ǹtì méjì mìíràn."*

*"Olúwa rẹ̀ sì wí fún un pé 'O ṣeun, ìwọ ọmọ ọ̀dọ̀ rere àti olóòtítọ́. Ìwọ ti jẹ́ olóòtítọ́ nínú ohun díẹ̀, èmi yóò fi ọ ṣe olórí ohun púpọ̀. Ìwọ bọ́ sínú ayọ̀ olúwa rẹ."*

> *"Níkẹyìn, ọkùnrin tí a fún ní tálẹ́ntì kan wá, ó wí pé, 'Olúwa, mo mọ̀ pé òǹrorò ènìyàn ni ìwọ ń ṣe ìwọ ń kórè níbi tí ìwọ kò gbìn sí, ìwọ ń kójọ níbi tí ìwọ kò ó ká sí. Èmi bẹ̀rù, mo sì lọ pa tálẹ́ntì rẹ mọ́ sínú ilẹ̀. Wò ó, nǹkan rẹ nìyìí."*
>
> *"Ṣùgbọ́n olúwa rẹ dáhùn pé, 'Ìwọ ọmọ ọ̀dọ̀ búburú, ìwọ mọ̀ pé èmi ń kórè níbi tí èmi kò fúnrúgbìn sì, èmi sì ń kójọ níbi tí èmi kò fọ́nká ká sí. Nígbà náà ìwọ ìbá kúkú fi owó mi sí ilé ìfowópamọ́ tí èmi bá dé èmi ìbá le gba owó mi pẹ̀lú èrè.*
>
> *"Ó sì pàṣẹ kí a gba tálẹ́ntì náà lọ́wọ́ rẹ̀, kí a sì fún ọkùnrin tí ó ní tálẹ̀ntì mẹ́wàá. Nítorí ẹnikẹ́ni tí ó bá ní a ó fún sí i, yóò sí tún ní sí lọ́pọ̀lọpọ̀. Ṣùgbọ́n láti ọwọ́ ẹni tí kò ní ni a ó ti gbà èyí tí ó ní. Nítorí ìdí èyí, gbé aláìlérè ọmọ ọ̀dọ̀, jù ú sínú òkùnkùn lóde, ibẹ̀ ni ẹ̀kún òun ìpayínkeke yóò gbé wà."*
>
> —Máátíù 25:14-30

Ìtàn yìí jẹ́ ọ̀kan tí a ti gbọ́ rí. Ọ̀gá fẹ́ lọ sí ìrìn àjò ó wá fi àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀ sọ́ ilé. Ó fún èkíní ní àpò wúrà márun un, èkejì àpò wúrà méji, èyí ẹ̀kẹta ní ó fún ní àpò wúrà eyọ kan.

Awọn méjì àkọ́kọ́ lọ bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ lójúkanna, wọ́n sì sọ àpò wúrà wọn di ìlópo méjì. Ọ̀gá wọn sì pàtẹ́wọ́ fún wọn ó sì yìn wọ́n fún isẹ́ tí wọ́n se. Sùgbọ́n èyí ọmọ ọ̀dọ̀ ẹlẹ́kẹta ni mo fẹ́ kí á gbé yẹ̀wò. Àpò wúrà kan ní wọ́n gbé fún sùgbọn kò fi se nkankan. Kódà, ó lọ bòó mọ́lẹ̀ ni títí ọ̀gá rẹ̀ fi dé.

> *Níkẹyìn, ọkùnrin tí a fún ní tálẹ́ntì kan wá, ó wí pé, 'Olúwa, mo mọ̀ pé òǹrorò ènìyàn ni ìwọ ń ṣe ìwọ ń kórè níbi tí ìwọ kò gbìn sí, ìwọ ń kójọ níbi tí ìwọ kò ó ká sí. Èmi bẹ̀rù, mo sì lọ pa tálẹ́ntì rẹ mọ́ sínú ilẹ̀. Wò ó, nǹkan rẹ nìyìí."*

Fíyèsí gbólóhùn rẹ̀ àkọ́kọ́: *'Olúwa, mo mọ̀ pé òǹrorò ènìyàn ni ìwọ ń ṣe ìwọ ń kórè níbi tí ìwọ kò gbìn sí, ìwọ ń kójọ níbi tí ìwọ kò ó ká sí."*

Kín ni ohun tí ó ńsọ? Ma sọ ńkan tí ó ńsọ gan fún ọ. Ohun tí ó ńsọ ni pé, Kílódè tí ma fi máa dáási? Tí ó bá nkórè níbi tí ìwọ kò gbìn sí, ta wá ni ẹnití ńsan owó fún irúgbìn àti pé tani ẹni ti ó túúká àti pé sé gbogbo isẹ̀ nà ni ó mu dàgbà?"

Níbayi, ó wá yé wa pé ọ̀gá rẹ̀ fún ní owó láti ra irúgbìn ni, sùgbọ́n nítorí ìwà àti ìse rẹ̀ nipé kò yẹ kí òun fi àkókò òun sílẹ̀ láti dásíi. Pé kòsí ohun kankan níbẹ̀ fún òun. Nítorí gbogbo èrè, àti èsì àbájáde lórí isé nà, ọ̀dọ̀ ògá òun ni ó lọ. Nítorí bí ó ti se rí ọ̀gá rẹ̀ bí ònrorò ènìyàn, ó wá mọ̀ ọ́n mọ̀ láti má dásíi. Ó gbìyànjú láti fí èrò rẹ̀ pamọ́ fún ọ̀gá nípa gbígbé owó rè pamọ́ nítorí tí ẹ̀rù mbá kí ó má ba pàdánu owó nà, ó wá lọ fi pamọ́ láti dáabòbò. Sùgbọ́n ọ̀gá rẹ bínú ó sì sọ fún pé kò bá dára nígbà náà ìwọ ìbá kúkú fi owó mi sí ilé ìfowópamọ́ tí èmi bá dé èmi ìbá le gba owó mi pẹ̀lú èrè tí o bá jẹ́ pé o fẹ́ mi ni.

Rárá, kì íse ẹ̀rù àti pàdánù owó nà ni ó mba ọmọ-òdọ̀ na; ẹ̀rù kí ni ó ma náa láti sé ní ó mba. Ó ti rí ọ̀gá rẹ̀ bí enití ó burú àti alágídí ènìyàn, tí ó sì jẹ́ wípé kì íse bẹ̀ẹ̀ lórí. Ọ̀gá rẹ̀ kì ise ònrorò rárá. Àwọn ọmọ-ọ̀dọ̀ mejì ni ó sì fún ní èrè pẹ̀lú ìgbéga ó sì tún pè wọ́n láti wá má jẹ̀gbádùn ní ilé rẹ̀ lẹ́yìn isẹ́ tí wọ́n ti se láseyọrí pẹ̀lú owó ọ̀gá wọn. Sùgbọ́n ọmọ-ọ̀dọ̀ tí à ńsọ yìí, nítorí bí ó ti se ńrí ọ̀ga rẹ, ó yàn láti má kopa nínú ohun tíi wọ́n se. Ẹ̀yí gan sì ni ohun tí ẹ̀sìn ńkọ wa—pé Ọlọ́run jẹ́ ònrorò pé kò sì sí èrè kankan nínú kí a má sisẹ́ pẹ̀lú rẹ̀, nítorinà kí wá ló dé tí ma fi máa sé?

Sùgbọn irú àwọ̀rán yií nípa Ọlọ́run kò rí bẹ̀ẹ̀ rárá kì íse òtító. Láti pe Ọlọ́run ní ìkà kòbújúmu. Ọlọ́run jẹ́ ìdàkejì ẹnití wọ́n fi pè. Olùsẹ̀san rere ati ẹni rere ni.

Sùgbọ́n ní báyii mo fẹ́ sọ̀rọ̀ lóri kókó kan pàtàkì nínú ìtàn yìí. Kí o sàkíyèsí rẹ̀ dáda láti rí ohun tí ògá nàa se pẹ̀lú wúrà tí ó gbà padà lọ́wọ́ ọmọ-ọ̀dọ̀ alaílérè ỳìí.

> *"Ó sì pàṣẹ kí a gba tálẹ́ǹtì náà lọ́wọ́ rẹ̀, kí a sì fún ọkùnrin tí ó ní tálẹ̀ǹtì mẹ́wàá. Nítorí ẹnikẹ́ni tí ó bá ní a ó fún sí i, yóò sí tún ní sí lọ́pọ̀lọpọ̀. Ṣùgbọ́n láti ọwọ́ ẹni tí kò ní ni a ó ti gbà èyí tí ó ní. Nítorí ìdí èyí, gbé aláìlérè ọmọ ọ̀dọ̀, jù ú sínú òkùnkùn lóde, ibẹ̀ ni ẹ̀kún òun ìpayínkeke yóò gbé wà.*

Sé mo kà á dada? Ó sì pàṣẹ kí a gba àpò wúrà náà lọ́wọ́ ọmọ ọ̀dọ̀ aláilére, kí a sì fún ọkùnrin tí ó ní tálẹ̀ǹtì mẹ́wa kì íse ẹnití ó ni mérin? Mo mọ̀ dájú pé kò tọ́ bẹ̀ ní ti òsèlum, sùgbọ́n ohun tí ó se nìyìí. **KÍ O FI ARABALẸ̀ DÁADA!!!!**

Ọlọ́run yóò fi èrò ńlá rẹ̀ àti àwọn iṣẹ́ àkànse fún àwọn ọmọ ṛe tí wọ́n nim èrè Rẹ̀ nínú ọkàn àti tí wọn sì ti fi ara wọn hàn bí olótìtọ́ àti ẹnití ó se gbáralé nínú iṣẹ́ kékeré tí wọn kọ́kọ́ se.

**ỌLỌ́RUN YÓÒ FI ÈRÒ ŃLÁ RẸ̀ ÀTI ÀWỌN IṢẸ́ ÀKÀNSE FÚN ÀWỌN ỌMỌ RẸ̀ TÍ WỌ́N NÍ ÈRÈ RẸ̀ NÍNÚ ỌKÀN...**

Ọlọ́run kì se òmùgọ̀. Yóò fi owó Rẹ̀ sí ibití yóò ti rí èrè ńlá padà ni.

Jọ̀wọ́ ronú nípa ohun tí mo sẹ̀sẹ̀ sọ tán—Ọlọ́run yóò fi owó rẹ̀ sí ibití yóò ti ríi èrè ńlá padà ni!

Níbáyìí, dájúdájú, Ọlọ́run kò sí ńinú oko- òwò *owó,* sùgb̀ọn ó wà nínú oko-òwò *ènìyàn*. Bí a si ti jẹ olótítọ́ sí iṣẹ́ àti farabalẹ̀ pẹ̀lú Rẹ̀, Yóò gbé wa ga pẹ̀lú ohun rere gbogbo ati fi ojúrere rẹ̀ fún wa pẹ̀lú.

Bẹ́ẹ̀ni, Ọlọ́run ni ẹnití ó yànfẹ́ nínú wíwo ẹnití ó nígbẹ̀kẹ̀lé nínú rẹ̀ pẹ̀lú láti yan iṣẹ́ àkànse ní onírúurú fún wọn. Àwọn tí wọn ti rí ara wọn bí olótítọ́ àti ẹnití ó se gbáralé tí ó le gbé iṣé ńlá lé lọ́wọ́ àti àwọn iṣẹ́ tí ólérè fún un.

Fiyèsí ìwà àwọn ọmọ̀ọ̀dọ̀ mejì tí wọ́n ní àseyọrí yìí—Wọ́n lọ ní kía láti lọ fi owó tí òga wọ́n gbé fún wọn lọ sìṣẹ! Kílódé tí wọn fi lọ lójú ẹsẹ̀? Nítorí ti wọ́n mò pé *ànfàní* ni ó jẹ́ fún àwon, kì ìse wàhálà ọmọ ọ̀dọ̀.

Ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn Ọlọ́run ní o rí sínsin Ọlórun bí làála, isé tí o kò gbọdọ̀ máse wọn kò ri bí *ànfàní*, tí ó jẹ́ gan.

Nígbatì èmi ati Drenda ńkọ ilé ọgbà ọmọ ilé ìwé ti Now Center Campus, aní láti se ìpinnu kan. A kò ju ọ̀ọ́dúnrún tí a jẹ́ ọmọ ìjọ lọ nígbàtí a sèpinu láti kó ibití ó tóbi tí yòò sì jẹ́ tiwa fún ìdàgbàsókè agbo àwọn onígbàgbọ̀.

A sètò bí atise le se ìkówójọ fún isẹ́ tí a fé se na tí a sì nwo owò tó tó míllịọnu mẹ́fà pọ̀ùn. Owó ńlá ni a sọ yí ní ìgbà náa. Èrò wa ní láti kọ́ àwọn ohun ìgbàlódé amáyéderùn tí ó tó bí míllíọ̀nù mẹ́rin ó lé ní igba owó pọ̀ùn tí a wá tún sírò àwọn irinsẹ́ tí ó tó míllíọ̀nù méjì pọ̀ùn mo ní pé a o ma kọ́ ọ lọ bí owó bá ti se ńwọlé. Kì íse ìgbà àkọ́kọ́ wa nìyíi tí àwa tí má ńlawọ́ sí isẹ́ Ọlọ́run ní sisẹ́, sùgbọ́n ó wá jẹ́ èyí tí ó ti tóbi ju tí a wà ná wá lára àwọn tí o ńse dé ibi tódé.

Síbẹ̀síbẹ̀, bí ìtàn àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ tí a sọ tí wọ́n mọ rere Ọlórun, níkiákía wọn fẹ́ jẹ́ ara àwọn tí ó ńkó owó nà jọ, a sì fẹ́ láti se ìfifun ní wá dé

ìpele tí yóò nílò ìgbàgbọ́ àti ìgbọ́ràn kún ohun tí a gbàgbọ pé Ọlọ́run ńbáwa sọ.

Ní ọjọ́ kan ni gbogbo ìjọ kéde ohun tí wọ́n ti ní àdéhùn láti se nípa isẹ́ àkànse na, Drenda àti èmi na wá sọ pé a ó fi ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ́ùn sí lẹ̀. Ní àsìkò tí a ńsọ yìí a kò ní ọ̀kẹ́-mẹ́wá pọ́ùn lọ́wọ́, sùgbọ́n a sì ní èso irúgbìn tí ó tó oní ọ̀kẹ́ kan pọ́ùn tí a fé gbìn nígbàna.

A mọ̀ pé, bí Ó ti se rí tẹ́lẹ̀, pé Ọlọ́run yóò fi hàn wá iboni àti bí a o ti se kóre iye owó na pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ eyí tí yó tún sẹ́kù sílẹ̀ fún wa.

Lẹ́yìn tí a ti gbin ọ̀wọ́ ohun tí a ní, awá bẹ̀rẹ̀ sí ní gbàdúrà nínú ẹ̀mí, a ńdúró fún ìtọ̀ni àti ìdarí ti ẹ̀mí pé níbo àti báwo ni a o se rí iye owó tí ó kù. Jẹ́ kí wá sọ fún ọ kí ó ba le yé ọ bí Ọlọ́run ti sé tí a fi rí owó tí ó kù, Mo ní láti sọ fún ọ pé aní ilé iṣẹ́ ti ìsúná kan láti bí ọdún mọ́kàndínlógójì sẹ́yìn. Ọ̀pòlọpò àwọn alágbàtà ni a ti bá sisẹ́ àti àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́, gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ fún ọ sáájú, ọ̀pọ̀ àwọn alágbàtà ilẹ isé ńlá tí a ti bá sisẹ́ yí ni wọ́n máa ńse àjọ̀dún ní ọdọdún àti se àsè àpèjẹ fún gbogbo àwọn oníbàárà wọn.

Ní ọdún tí a ńsọ yìí gan, ọ̀kan lára wọn ni ó fi ìwé pe èmi àti Drenda láti wá sí Lọ́ndọ́nù, ní ìlú ọba (England), fún ìpàdé àpèjọ na. A dé sí ilé ìtura tí ó dára kan ní òpin ìlú, ibẹ̀ mà rẹwà gan, bí wọ́n ti nsọ ní Lọ́ndọ́nu̱.

Ó da, ilé iṣẹ́ na ti sètò kan sí apá kejì ìlú lọ́húún, igbákejì Àare wá pe èmi àti Drenda láti lọ papọ̀ pẹ̀lú rẹ̀ nínú ọkọ̀ kanna sí ibi ètò na, tí a sì fi tayọ̀tayò gbàá. Nígbàtí a ńlọ lójú ọ̀nà nínú ọkọ̀ na, igbákejì Àarẹ dúpẹ́ lọ́wọ́ wa fún gbogbo iṣẹ́ tí ati fi sọwọ́ sí wọn ó wá bẹ̀rẹ̀ sí ní sọ nípa ètò míràn titun ti ó ní ẹ̀bùn ninú tí wọ́n sẹ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀ rè nínú ọdún nà fún wa.

Ó tún sàlàyé rẹ̀ fún wa bí ó ti se ńlọ àti bí wọn ti se àgbékalẹ̀ tí ẹ̀bùn tí wọ́n ó san fún ẹgbẹ́ tí ó bá sèdúrò fún ọjà tí wọ́n bá ńtà. Inú mi dùn bí ó ti se ńsọ̀rọ̀, bí mo ti mọ̀ pé ati se ọ̀pọ̀lọpò isé tótó láti yẹ fún wa láti gba irú ẹ̀bùn tí ó ńsọ̀rọ̀ nípa re.

Nígbànáà, bí mo ti wá bèrè fún àlàyé síwájú si, kía ni ó ti dá mi lóhùn pé ilé iṣé wa kò lẹ́ẹ̀tọ́ sí àwọn ẹ̀bùn ètò náà lórí àlàkalẹ̀ ti ìbásepò wa pẹ̀lú ilé isẹ tirẹ̀.

Mi ò le gbàgbó. Kílódé tí yóò se gbogbo àwọn àlàáyé yí tán tí ó sì ti fi ọkàn mi sórí ètò ńlá yí kí ó wá yọmí kúrò bẹ́ yẹn níkẹ́yìn? Bẹ́ ni mi ò mọ bí ìbásepọ̀ wa pẹ̀lú ilé isẹ́ rẹ̀ tí ó ńso ti rí tí ó wá le má mú wa yẹ fún ẹ̀bùn na.

Síbẹ̀ lóòtọ́ mo sìtún bèrè àwọn ìbéèrè síwájúsi, kò sì fún mi lésì tí ó jágara. Ohun kan tí mo mọ̀ dájú nipé mi ò le gba ẹ̀bùn nà ó ti sọ ọ́ ye.

Ọdún gorí ọdún isẹ́ wa sì dára gan nínú ọdún nà, mo wá rò pé kín tún pe wò lẹ́ẹ̀kansi láti wáàdí nípa ẹ̀bùn tí ó sọ. Síbè, nígbàtí mo pèé ní àkọ́kọ́, mi ò ri ba sọ̀rọ̀, mo wá kọ ìfiránsẹ kan sílẹ̀ fun ni ọ̀dọ̀ amúgbálẹ́gbẹ rẹ̀ pẹ̀lú ìbérè mi.

**Sé O RÍI ỌLỌ́RUN NI OLÙSÈSAN! ÈRÈ SI WÀ NÍNÚ KÍ ÈNÌYÀN LAWỌ́ SÍ ISẸ́ ÀKÀNSE ỌLỌ́RUN.**

Ní ọjọ́ kejì, amúgbálẹ́gbẹ rẹ̀ pè mí padà, pẹ̀lú ohùn líle, ó ní sebí igbákejì Ààrẹ ti sọ fún mi ní ọdún tó kọjá pé mi kò yẹ, láti gbà á, kò sì sí nkàn tí ó le se nípa rẹ̀.

*Ó dára, ó dára bẹ́ẹ̀* molérò, *pé mo gbìyànjú.*

Nísinsìnyí, mo ti gbàdúrà pé níbo ní mo ti fẹ́ rí ọ̀kẹ́-mẹ́sàán pọ́ùn, mo gbọ́ tí Ẹ̀mí Mímọ́ sọ fún mi láti pe igbákejì Ààrẹ kín sì bí léérè fún ẹ̀bùn yẹn lẹ́ẹ̀kansi. Mo fẹ sọ fún ọ pé mi ò bèrù látgbọ́ nkan tó sọ. Lẹ́yìn ìrírí mi láti bí ọdún méjì tí mo ti nbií léèrè, mo ti mọ ibití ó dúrólé. Ó ti sọtẹ́lẹ̀, kóyémi. Toríbè, mo lérò pé ma kàn fi àtẹ̀jíṣẹ́ ránṣẹ sí ímeelì rẹ̀ ni láti tún gbọ́ ohun tí ó fẹ́ sọ, kín sọ bẹ́ẹ̀.

Lẹ́yìn ọjọ́ keèje mo rí èsì tí ó kọ sí mi, sí ìyàlẹ́nu mi ò ní òun tí tundàrò òun ṡi ti pinnu láti fún ilé ìṣẹ wa ní ẹ̀bùn pẹ̀lú. Sí ìyàlẹ́nu, ọ̀kẹ́-mẹ́wa-pọ́ùn ni ẹ̀bùn owó tí ó fẹ́ fún wa! Níbáyìí, ibití ó tilẹ̀ dára jùlọ nínú rẹ̀ nìyìí. Àdéhùn isẹ́ yi ti wà nínú àkọsílẹ̀ fún wa fún ỌDÚN mẹ́rìnlá tí a o sì maa gba ẹ̀bùn ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ́ǹu yií bẹ́ẹ̀ ní ọdọdún láti ìgbànáà lọ.

Sé o wá ríi, Ọlọ́run ni Olùsẹ̀san! Èrè sí wà nínú kí ènìyàn lawọ́ sí isẹ́ Ọlọ́run.

Èló ni a wá ná èmi àti Drenda láti fúrúgbìn ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ́ùn ni?.

Ọdún bíi márùn ún tí kọjá báyìí, gẹ́gẹ́ bí ìjọ a wá pinnu pé ó yẹ kí á tún se ìkówójọ nítorí a sì nílò owó láti parí àwọn nkan díẹ nínú ìjọ àti tún le ra àwọn ohun èlò míràn. Lẹ́ẹ̀kansi Èmi àti Drenda tún ròó wípé èló ni a máa fi sílẹ̀ fún isẹ́ àkànse náà a sì pinnu àti fi ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta pọ́ùn sílẹ̀.

Wow, ọ̀pọ̀ owó ni èyí o. Sùgbọ́n a rò pé a le gbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run ní nítorí arim ohun tí ó se pẹ̀lú ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ́ùn. Bẹ́ẹ̀ni, a si fumrúgbìn ohun tí a lè se nim àsìkò na tí mo rò pé bí ọ̀kẹ́-mejì-àbọ̀, tí a sì ńgba Ẹ̀mí Mímọ́ gbọ́

láti tún fi hàn wá níbo àti báwo ni a o ti se rí ọ̀kẹ́-méjì-le-ní–ogún-ó-lé–ní-ẹgbaàrún.

Mo rò pé lẹyìn ọ̀sẹ̀ kẹfà, ni mo wá gba ìwé àkíyèsí kan pé àwọn àyípadà yóò wà lórí àdéhùn tí wọ́n ti se bí a o ti se máa sanwó ní ilem iṣẹ́ wa. Lẹ́yìn tí a wá se ìsirò lórí àwọn àtúnse àti san owó nà a wá rí wípé a ti ní tom ọ̀kẹ́- mọkàn-lé-ní-ọgbọ̀n ó-lé–ní-ẹgbaàrún tí yóò sẹ́kù nílẹ̀ fún wa fún bí ọdún mẹta tí ó mbọ̀. Ó tunilára kùlẹ̀ẹ̀, àbíi? Ó da, dá a ròpé kínni? Sé o wá rí i àyípadà àdéhùn tí wọn se yìí ti wá wàbẹ láti bí ọdún mọ́kànlá, a sì tún gba òsùwọ̀n àdéhùn bí ó ti lọ sókè tó ní ọdọdún.

Lẹ̀ẹ̀kansii, èló ni a náa èmi ati Drenda láti lawọ́ sí iṣẹ́ àkànse Ọlórun?

Torimbẹ̀, má a ramntí pem Ọlọ́run jẹ́ Ọlọrun èrè. Ó dára òn si ni Olùsẹ̀san.

ORÍ KẸTA

# SÉ O KÓJÚÒSÙNWỌ̀N

Mo lérò pé gbogbo ènìyàn ni ó ti gbọ́ nípa ìtàn kérésìmesì àti nípa àwọn ọba mẹ́ta tí wọ́n mú èbùn wá fún Jésù, wúrà, fàdákà, àti òjìá. Ǹjẹ́ o ti lẹ̀ ti ròó rí pé èló ni àwọn nkan wọ̀nyìí tó níye? Ìbéèrè tí ó dára nipé, "Kílódé tí wọ́n fi mú àwọn ẹ̀bùn yí wá fún un ná?"

Ó dá, pẹ̀lú àwọn ìwádí kan, a rí wípé ohun tí ó wọ́pọ̀ ni ní ayé ìgbàanì láti fi olá fún ọmọ-ọba pẹ̀lú irú àwọn ẹ̀bùn wọ̀nyìí, nítorí tí wọ́n ríi bí ọba lọ́la.

Nígbàtí wọ́n gbé lé ìwọ̀n ọ̀kokan nínú àwọn ẹ̀bùn yìí tó ọ̀kẹ́-máàrún un pọ́nù àti ẹgbẹgbẹ̀rún owó dọ́llà.

Àwọn amòye yóò ti ka iwé mímọ́ àti àwọn àsọtẹ́lẹ̀ nípa bíbọ̀ Mèssáyà, bí wọ́n sì ti rí ìràwọ̀ ni wọ́n ti gbà pé Òn ni ó dé, wọ́n wá rin ìrìn àjò lọ sí ọ̀nà jínjìn rere láti mú ẹ̀bùn wá fún un.

Èròngbà pé wọn bá Jésù ní ibùjẹ́ ẹran kì íse ohun nì nkan tí ó sẹlè, kódà bí ó tilẹ̀ hàn bẹ nínú àwọn eré tí a máa ńse ní àsìkò kérésìmesì. Àwá mọ̀ nítorí ìwé Máttíù sọ àwọn nkan wọ̀nyíi

> *Bí wọ́n tí wọ* *<u>inú ilé náà</u>*, *wọn rí ọmọ ọwọ́ náà pẹ̀lú Maria ìyá rẹ̀, wọ́n wólẹ̀, wọ́n foríbalẹ̀ fúnun. Nígbà náà ni wọ́n tú ìṣúra wọn, wọ́n sì ta Jesu lọ́rẹ: wúrà, tùràrí àti òjìá.*
>
> —Máttíù 2:11

Ní ilé Jésù ni wọ́n ti lọ báa, kì íse ní ìbùjẹ́ ẹran. Ibití a kà yìí fi hàn pé ọ̀dọ́mọdé ni, kì íse ọmọ owọ́. Toríbẹ̀. A jẹ́ wípé ó pẹ́ díẹ̀ kí àwọn amòye tó dé ibẹ̀.

Ẹlẹ́keji, kòsí ẹnìkan tí ó mọ iye tí àwọn amòye náà jẹ́. Bíbélì kò sọ iye àwọn amòye tí ó wá fún wa, sùgbọ́n ó kọ àwọn ohun tí wọ́n mú wá sílẹ̀. Ní ìgbàna fàdákà àti òjìá jẹ́ àwọn ohun tí ó ni iye lórí gan ju wúrà lọ, torínad àwọn ẹ̀bùn tí wọ́n mú wá ní iye lórí gan ni.

Kílódé tí mo fi ńsọ èyìí? Ó da, jẹ́ kí nbi ọ́ léèrè, "Kílódé tí ó fi ròpé àwọn amòye wọ̀nyìí ni ó mú àwọn ẹ̀bùn nà wá?

Mo le sọ idí rẹ̀ fún ọ—Josẹ́fù nílò ìpèsè fún àwọn isẹ́ tí ó ní láti se.

Rántí pé…

Ọlọ́run máa ńpèsè fún isẹ́ Rẹ̀—nígbogbo ìgbà!

Faith Life Church kún fún àwọn ènìyàn. Ní òpin àwọn ọ̀sẹ̀ ó máa kún, bẹ́ẹ̀ni ní àrin ọ̀sẹ̀ na bí a ti se ńdá àwọn ọmọ tí ó lé ní igba lẹ́kọ, kún pelú àwọn ẹgbẹ́ kékèké àti àwọn òsìsẹ́. A ti nílò àyè tó fè si. A wá ńjíròrò lórí pé bóyá kí á tún lọ sí ọgbà ilé ẹ̀kọ̀ míràn tàbí kí á ma gbé ibití awà báyìí sókè. A sì pínnu láti má sisẹ́ lórí méjèjì ni ẹ̀ẹ̀kanna.

Toríbẹ, a kó àwọn ìgbìmọ̀ kan jọ láti má sisẹ́ lórí bí a o ti se rí ibití a le lò fún ọgbà míràn, a sì júwe àwọn agbègbè tí wọn le lò fún wọn.

Nígbànáá, ni àsìkò kanna, a bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìgbésẹ̀ àkọ́kọ̀ ní yíya àwòrán ilé, kí àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ sisẹ́ ti wọn tí isẹ́ sì ma tẹ̀síwájú. A wá gba àwọn abáníkọ́lé àti a kọ́sẹ́mọsẹ́ ayàwòrán ilé àti ìgbìmọ̀ ìkọ́lé gbogbo wọn papọ̀ ni wọ́n ti ní ìmọ̀ nínú isẹ́ ilé kíkọ́.

A wá sàkíyèsí pé àwọn ìsòro kan yóò wáyé nípa ti sísọmọ́ ilé nà. Èyí tí ó ganíbẹ̀ nipé a kò ní gọ́tà tí omi ó mà gbà a lọ kòsị̀ sì omi ni ile wa. A ńlo omi kànga àti ètò ti ilé ịsẹ akólẹ̀ fún gọ́tà wa.

Wọ́n ti sọ fún wa tẹ́lẹ̀ pé a kò ní le kọ́ ilé sórí ara wọn tàbí fi kún ilé tó wà lórí saarè ilẹ̀ mẹ́rìndínlógójì tí a fi kọ́ ọgbà ilé ẹ̀kọ́ wa àyàfi tí a bá ni omi àti gótà ní ara ilé nà, bí a sì ti sọ ibití a mọ̀ pé wọ́n le gbà láyè ni ó ní orúkọ. A mọ wípé tí a bá ti dé ibẹ̀ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ilé titun ní ó wà ní àyíká wa ti mọ́ rò pé dájúdájú wọn ò ti bá isẹ́ dé ibi àti mú kí omi àti gọ́tà tíì súnmọ́ wa tó.

À wa rí wípé kò tí le tíì sí omi tàbí ọ̀pá gọ́tà ní àdúgbò wa rárá, kì íse ọ̀rọ̀ kí á kàn rọra gbàá ní tòsí níbẹ̀. Wọn kò tíẹ̀ sí níbẹ̀ rárá.

À wa bẹ̀rẹ̀ isẹ́ lórí bí a o ti se mú omi àti la gọ́tà dé ibi ilé ti à ńkọ́ àti bí ao se san owó tí a sì ní láti tún san ọ̀pọ̀ owó padà bí pé ǹkan míràn titun ní tí a san owó fún wa láti le sopọ̀ mọ́ ìlà na. O kò ní fẹ́ mọ iye tí wọ́n ní yóò ná wa.

Toríbẹ̀, a ní láti padà sí inú ìlú àti lọ tún ètò wa yẹ̀wò àti àkókò tí a ní fún àwọn ètò yí láti bẹ̀rẹ̀ tí a sì lérò pé wọn yóò fẹ́ láti sún àkókò na síwájú síi díẹ̀, nítorí ìdàgbàsókè sẹ̀sẹ̀ ńbá àdúgbò na ní lóòtọ́ gbogbo ǹkan yìí nà ni wọ́n ó sì nílò níbẹ̀ ní ọjọ́ wájú. Sùgbọ́n wọn kò tilẹ̀ bìkítà. Ìgbàwo ni wọn sọ pé yóò tó kí àwọn tó le se é? Kì íse ní kíakía báyìí.

A mọ̀ pé a kò ní le dúró pẹ́ lọ títí fún omi àti ọ̀pá gọ́tà kí ó tó dé àdúgbò na, toŕibẹ a pinnu láti fi ìyẹn sílẹ̀ ná a sì bẹ̀rẹ̀ sí ní wá ibití a ó fi se ọgbà ilé ẹ̀kọ́ bí èròǹgbà wa tẹ́lẹ̀. (ó ti tó ọdún mẹ́rin séyìn tí a ti se ìpàdé sí ìgbad tí mo ńkọ ìwé yìí, wọn kò sì ti rí ǹkan se nípa ọ̀pá gọ́tà àti ti omi ìgbàtí yóò jẹ́ síse.)

## ỌLỌ́RUN MÁA ŃSE ÀWỌN ÌNÁWỌ́ IṢẸ́ ÀKÀǸSE RẸ— NÍGBÀGBOGBO!

Ó da, àwọn ìgbìmò yìí fi osù mẹ́fà gbáko wá ibití ó dára tí a lè kọ́ ọgbà ilé ẹ̀kọ́ sí tí wọn kò sì mú ǹkankan jáde. Ó wá dàbim ẹni pé kòsí ilé tí ó dára bí ǹkan tí a sàpèjúwe rẹ̀ tí a le rí yá tàbi rà. Toribẹ a wá wòó wípé a le lọ yá ibi ilé ìgbafẹ́ ní àdúgbò na, àní fún òpin ọ̀sẹ̀ nìkan, tí yóò sìná wa ni ẹgbàáẹ̀ẹ́dógún pọ̀ùn ní osù kan. Lórí gbogbo iye tó máa ná wa, aní láti sètò àti bí a ti se pín ní àrin ọ̀sẹ̀ kọ̀kan, Èmi ò sì fẹ́ láti fi àwọn ènìyàn mi sí irú ipò yìí. Ohun tí mo fẹ́ ni kí a ní àyè ti wa tí a ó maa se àkóso fúnra wa. A kò ní ìsinmi nípa ibití à ńlò lọ́wọ́lọ́wọ́.

A wá tún wòó pé bóyá kí a lọ yá àyè tí ó wà níbi ilé ìtajà kan tí ó ní orísirísi àwọn ìsò lọ. Sùgbón nígbàtí a se àgbé yẹ̀wò iye tí a máa ná láti se àwọn àtúnse kí ó le dùn ún wò, a rí pé kì íse ohnu tí a le gbà pẹ̀lú.

Ọ̀kan lára ohun tí a sírò àti mójútó nípa ilé tí à ńwá ni pé ó gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí yóò wúlò láti sàtìlẹ́yìn fún ẹ̀kọ́ àwọn ọmọdé wọ̀nyií ní àrin ọ̀sẹ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìdílé ni ó ńkọ́ ẹ̀kọ́ nílé nínú ìjọ wa, a sì tún máa ńgba àwon aláfọwọ́sowọ́po ní àlejò bákanna bí àwọn kílásì ní ọ̀sẹ̀ ọ̀sẹ̀. Ati sọ ní ọ̀pọ̀ ìgbà pé ní ọjọkan ó seése kí a ní ilé ìwé, ilé ìtọ́jú àwọn ọmọdé, àti ètò lẹ́yìn ilé ìwé, àti àwọn ètò míràn tí yóò se ànfàní fún àwọn agbègbè wa. A fé láti wá àye tí yóò gbàwá láti se àwọn ǹkan yìí. Ati fúrúgbìn nitorí ilé tí a fẹ́ kọ́, àti gbà pé a ti rí ibití ó dára láti fi kọ́ àwọn ohun tí a nílò, kò kàn ti fojú hàn ni.

Èmi àti Drenda yẹ kí á lọ sí ìpàde kan ní Fort Worth, Texas, láti se àtìlẹ́yìn fún ilé iṣẹ́ Victory Television Network. Nígbàtí a wà níbẹ̀, bí mo

ti jókòo ní ibi ètò na, ní Olúwa ba mí sọ̀rọ̀. O ní, "*Mo fẹ́ kí o fúrúgbìn ọ̀kẹ́-máàrún pọ́ùn sí ilé iṣẹ́ yí. Kí o lọ sí ilé nínú ìjọ rẹ, kọ sọ̀wédowó nà jáde , kí o wá mú dání nínú ìsìn kí o sì wá pàsẹ lórí irumgbìn ná pé wa rí ibití ó dára fún ilé tí ẹ fẹ́ kọ́. Bákanna, kí o bá Sàtánì wí kí o sọ fún kí o má dásí ọ̀rọ̀ iṣẹ́ Mí mọ́. Kí o sì sọ pé o ti rí bẹ̀ bí o ti fúrúgbìn na*."

Nkàn tí a se gan nìyí. A lọ sí ilé, mo wá pe akápò mí mo sọ fún pé kí ó kọ sọ̀wédowó ọ̀kẹ́-máarún pọ́ùn jáde fún Victory Television Network. Mo wá ńmu lọ sínú ìsìn kọ̀kan, gbogbo ìjọ si sowọ́pọ̀ pẹ̀lú mi bí a ti ńfúrúgbìn irúgbìn na fún kíkọ́ ilé tó dára. A sì bá Sàtánì wí a sọ fun pem kí o jáwọ́ láti ma dásí àti dá iṣẹ́ wá.

Ní ọjọ́ kejì tí ńse òwúrò ọjọ́ Ajé, a gba ìpè láti ọ̀dọ̀ ọmọ wa obìnrin, tí o sọ pé nígbàtí a wà nim ìpàdé ní Texas, àwọn abániwálé bánitalé ti gbà láti fi ibi ohun ìní kan tí ó dára hàn wọ́n. Kì íse yíyálò bẹ́ sì ni kò sí nínú ìsúná wa, bí wọ́n ti se gbésílẹ̀ fún títà ní $7.9 milliọnù pọ́ùn. Sùgbọ́n ó tó́ bẹ̀ ó tún jù bẹ lọ ibití àwọn bánkì gbà lọ́wọ́ ẹnití ó ní ni.Ó ní ibẹ̀ mà dára gan fún ọgbà ilé ẹ̀kọ́, sùgbọ́n, ó mọ̀ wípé owó kò le jáwa ní tànmọ. Sùgbọ́n síbẹ̀ ó fẹ́ mọ̀ bóyá a máa fẹ́ kí á wá láti yẹ ibẹ̀wò. Aní bẹ́ẹ̀ni.

Ní́ òwúrò ọjọ́ ìségun. A lọ láti yẹ ohun ìní ná wò. Orí saarè ilẹ̀ méje ni ọgbà ilé ìwé girama aládani wà. Ó ní ilé alágbékà mẹ́ta àti ilé ńlá méjì, bákanna ilé kan tún wà lórí ilẹ̀ na. Ó ní ipa-ọ̀nà eré-sísá, pápá ìseré tẹnisi (bọolù aláfọwọ́ gbá ló ri tábíli) àwọn yàrá tí wọ́n ti ńgbé ohun tó wúwó, ilé isẹ́ ọnọ̀ pẹ̀lú lábù àwòrán, ewìrì tí wọ́n tí ń mọ ìkòkò méjì ló wà níbẹ̀, pẹ̀lú yàrá tí ó kún fún irinṣẹ́ ìránsọ àti iṣẹ́ ọnọ̀ tí wọ́n ti pèsè, ọ̀pọ̀ ohun èlò orin nínú yàrá orin, àti àwọn nkan míràn bẹ́ẹ̀bé lọ.Gbogbo ohun-ìní nà ni wọ́n ti ṗesè sílẹ̀ àti kún fún ọ̀pọ̀ ìsúra tí wọ́n ti pèsè síbẹ̀.

Bí a ti se nlọ yíká ohun iní nà, mo ri pé ibẹ̀ dára gan ni. Sùgbọ́n bákanna, a mọ̀ pé a kò le tọrùn bọ gbèsè rẹ̀. Owó tí aní kò ju bi milliọnù mẹ́ta pọ́ùn lọ́wọ́ lọ tí a ti kójọ fún ìkọ́lé, tí ó jẹ́ wípé a ní láti yá bi míllịọnù máàrún un síi.

Ní alẹ́ ọjọ́ nàa aní ètò jíjẹ óunjẹ alẹ́ pẹ̀lú ọ̀kan lára àwọn alábásiṣẹ́pọ̀ ní ilé iṣẹ́ ìránṣẹ́ wa. Bayìí, ó ti fẹ́ ẹ̀ tó ìgbà mẹ́rin ọ̀tọ̀tọ̀ tí ó́ ti yẹ kí á lọ fún óunjẹ alẹ́ yí sùgbọ́n tí kò sí àyè fun nítorí iṣẹ́ wa, sùgbọ́n ní alé ọjọ́ nà ni a lọ.

Bí a ti ńsọ̀rọ̀, ọ̀jọ̀gbọ́n kùnrin na bèrè nípa iṣẹ́ àkànse ilé tí a ńkọ́, mo

wá sàlàyé gbogbo ìdíwọ̀ tí a ńrí ló rí rẹ̀. Ó wá wojú mi ó ní, " Sé o mọ̀, mo ńrò wípé ẹ̀ bá gbé sísí ọgbà ilé ẹ̀kọ́ nà yẹ̀wọ̀ dípò nkan tí ẹ̀ ńse" Mo wá sọ fún pé àwa gan ti gbà bẹ́ẹ̀, àti pé a ti ńfojú wá ilẹ̀ tí a lè lò ó ti tó bí osù mẹ́fà sí àsìkò yìí tí a kò sì tí rí òkankan. Síbẹ̀síbẹ̀, a wá sọ fún pé a sẹ̀sẹ̀ rí ibìkan lónìí tí a rí pé ó dára gan fún ohun tí a fẹ́ se, sùgbọ́n kì íse fún yíyálò owó rẹ̀ sí ga ju iye tí a ní lọ́kàn lọ.

Ó wá bèrè àwọn ìbéére díẹ̀ nípa ibití a ńsọ yìí, nígbàna ni ó wá wojú Drenda óni , "Tí wọ́n bá wá fi fún yín lọfẹ ńkọ́?" Drenda kò sọ̀rọ̀ nítorí ó rò wípé àwàdà ni ó ńse. Ó tún túnsọ lẹ́ẹ̀kansi, Drenda, àti Èmi sọ pé tí ó ba lọ jẹ́ ọ̀fẹ́ ni ńkọ́?

Ó bèèrè wípé, "kín ni nkan tí ẹ ńsọ?"

"Màá kọ sọ̀wédowó fún yín ni" Ni ó sọ.

Èmi àti Drenda jókòó síbẹ̀ ní ìyanu.

Níkúkúrú èdè, ó san owó naà. A wá ní láti ná owó díẹ̀ láti se àwọn àtúnse díẹ̀ tí a sì tún ilé nà se láti bá ohun tí a fẹ́ fise mu. Àbájáde rẹ̀ na ni ọgbà ilé ẹ̀kọ́ tí ó dára. A sì san owó ilé nà!

Mo le má le sètò fún ibití ó dára fún ọgbà ilé ẹ̀kọ́ tí a nílò tó. Ohun gbogbo nípa rẹ̀ ni ó dára tí ó sì péye. A sì se ìdíyelé àgbéyẹ̀wò fún ilé iṣẹ́ adójútòfò wa. Gbogbo rẹ̀ sì wá jásí mílliọnù mọ́kànlá owó pọ̀ùn pèlú ohun gbogbo tí o wà níbè.

Óyá ròó wò: A wà ní ọgbà ilé ẹ̀kọ́ tó ó tó mílliọnù mọ́kànlá pọ̀ùn níye pẹ̀lú àyè ìwọ̀n bàtà ẹsẹ̀ tí ó jẹ́ ẹ̀ẹ̀dẹ́gbàrún-lé-ní-ọ̀kẹ́-mẹ́rin ó lé okan àyè tí a ti sanwó fún!" Sé o kò nífẹ̀ sí irú ìtàn yìí?

Gẹ́gẹ́ bí mo ti máa ńsọ, pé Ọlọ́run ni ó má ńsiṣẹ́ ara Rẹ̀. Iṣẹ́ ìránṣẹ Rẹ̀ ni kì íse tiwa. Àwá kàn jẹ́ alábásiṣẹ́pọ̀ pẹ̀lú Rẹ̀ ni nínú oko-òwò tí ìdílé.

Níbayìí, jẹ́ kí nsọ ohun tí ó selè sí ọkọ àti ìyàwó tí wọ́n san owó ilé nà fún wa. Ní àkọ́kọ́, nítori ́tí wọ́n fagile níbáyìí wọ́n wa le gba ore tí wọ́n ti se, níse ni wọ̀n dín owó orí wọn kù ju iye ti wọ́n san fún owó ilé nà lọ.

## IṢẸ́ ÌJỌBA ŃSIṢẸ́ NÍ GBOGBO ÌGBÀ!

Bíi báwo? A wá fi orúkọ wọn sọ ilé nà fún bí ọdún méjì. Nígbàna ni wọ́n wa fi ilé nà tọrẹ fún ilé iṣẹ́ ìránsẹ́ a wá tún àdíyelé àgbéyẹ́wò ilé nà se.

Èyí ni irú ète ìlànà tí o gbọdọ̀ mọ̀ tí o bá jẹ́ pásítọ̀ tí o nílò ilé. Toribẹ̀, ilé nà wa di ọ̀fẹ́ fún àwa méjéjì nítorí tí a fi ọgbọ́n sètò owó orí rẹ̀ ní sísan

ní agbọn ọ̀dọ̀ rẹ̀. Kódà kì ise èyí tí ó jẹ́ iyanilẹ́nu jù nínú ìtàn na nìyìí.

Àwọn alábásiṣẹ́pọ̀ wá yìí ńgbìyànjú láti ra oko-òwò míràn nínú ìlú tí wọn fẹ́ tà ní àkókò tí ó ńfojúsí ohun ìní yi. Bíótilẹ̀jẹ́pé, ó fẹ́ láti san owó, síbẹ̀ àwọn tí ó ní kọ́kọ́ láti fàsẹ sí pé kí wọ́n ta ibi tí ó fẹ́ láti rà yí, ó wá seni láàánú pé wọ́n ní àwọn ti tàá fún elòmíràn nígbàtí wọ́n padà dé. Inú rẹ̀ kòdùn bí wọ́n ti se yẹ àdéhùn tí wọ́n pinnu. Ó wá sọ fún mi pé òun kò fẹ́ jáwọ́ nínú rẹ̀ bẹ́ yẹn; nítorí ọkàn rẹ̀ kò kúrò níbẹ̀.

Nígbàtí ó wa fúrúgbìn owó sí ti ilé tí àwá fẹ́ kọ́, ó sọ fún mi pé òun se be nítorití òun gbàgbọ́ pé àwọn tí ó ni ibití òun fẹ́ rà na yóò ní ìyípadà ọkàn,nítorítí òun wà ní ipò tí ó tayọ ní ti ìsúná yàtọ̀ sí àwọn ẹnikejì òun sì setán láti kó owó da sílẹ̀ ni.

Ó da, láìpẹ́, léyìn tí wọ́n ti sèdúnádúrà tán lóri ohun ìní nà, ó gba ìpè láti ọ̀dọ̀ àwọn tí ó ni ohun-ìní nà, tí wọ́n sàlàyé fún pé ọ̀rọ̀ kò lọ bẹ́ mọ́ bí àwọn ti sọtẹ́lẹ̀ pé tí ó bá sì tún nífẹ síi a jẹ́ pé ó ti di tírẹ̀ nìyẹn. Ó dá àwon lóhùn pé bẹ́ẹ̀ni, ó dájú pé, mo fẹ́e.

Lẹ́yìn bí ọ̀sẹ̀ melo kan sáájú ìgbàtí ó fẹ́ bẹ̀rẹ̀ oko-òwò tí ohun-ìní titun yìí. Ó rí àwọn ńkan tí kò retí tí ó já sí lọ́wọ́ pátápátá ti ó sì pèsè gbogbo owó tí o nílò láti fi san owó fún oko-òwò rẹ̀ titun na. Tí kò sí wá nílò láti fọwọ́ kan owó tí ó sètò sílẹ̀ tẹ́lẹ̀ láti fíra gbogbo rẹ̀ mọ́. Ó sọ fún mi pé ó wà dàbi ìgbàtí ènìyàn gba oko-òwò náà lọ́fẹ ni.

Háà, nígbàtí ó ti wá ràá tán, ìdíyelé àgbéyẹ̀wò rẹ̀ wá ju ìlópo méjì iye tí ó san fún lọ. Nígbàtí ó pè mí ní ọjọ́ tí ó pè mí tí ó ti san owó ohun ìní nà tán inú rẹ̀ dùn gan ni.

Ìjọba ńsiṣẹ́ ni gbogbo igba!

Alábásisẹ́pọ̀ wa yìí jẹ́ ẹnití ó lawọ́ sí iṣẹ́ Ọlórun àti gbọ́ràn láti má tẹ̀lèé àti kí o wá wo ohun ti Ọlọ́run se fún àwa méjéjì. A fúrúgbìn sí ilé isẹ́ Tẹlifisiọ́nù titun, ọ̀kan nínú ohun tí Ọlọrun palásẹ, kí o wá wo ǹkan tí ó sẹlẹ̀ fún wa.

Bí ó bá jẹ́ ẹnití ó lawọ́ sí isé Ọlọ́run àti àwọn ènìyàn Ọlọ́run yóò maa sí àwọn ìlẹ̀kùn tí ó kò lérò pé o wà fún ọ ni.

Àwọn ènìyàn má ńbimí ní gbogbo ìgbà ni pé, Garry, tí o bá fún mí ní kọ́kọ́rọ́ kan tó se kókó lóni tónise nípa ìsúná ti Ìjọba, kín ni yóò jẹ́?

Ó da, ọ̀polọpọ̀ nkan ni ó wà tí mi ò bá fẹ́ láti sọ fún ọ tódájú. Sùgbọ́n ìmọ̀ràn tí mo fẹ́ sọ fún ọ yìí níyelórí. Rí dájú pé o fiyèsi àwọn ìlànà òfin tí Ìjọba yìí.

**<u>Tí o kò bá rí ǹkan míràn mọ́ nínú ìwé yìí: Rí àwọn nkan wọ̀nyìí</u>**!

Mo fẹ́ kí a lọ wo ìwé Lúkù 4 bí mo ti se fẹ́ bèrè láti máa fi àwọn òfin wọ́nyìí tí íse ti Ìjọba hàn fún ọ. Mo mọ̀ pé ẹsẹ̀ tí a fé kad yí gùn díẹ̀ ju èyí tí mo má sọ lọ, sùgbọ́n tí a bá ka gbogbo ẹsẹ̀ na yóò fún ọ ní ànfàní àti mọ ohun tí ó nsẹlẹ̀ àti ìdim tí Jésù fi dáhùn ní ọ̀nà tí ó fi dáhùn.

> *Ó sì wá sí Nasareti, níbi tí a gbé ti tọ́ ọ dàgbà: bí ìṣe rẹ̀ ti rí, ó sì wọ inú Sinagọgu lọ ní ọjọ́ ìsinmi, ó sì dìde láti kàwé. A sì fi ìwé wòlíì Isaiah fún un. Nígbà tí ó sì ṣí ìwé náà, ó rí ibi tí a gbé kọ ọ́ pé:*
>
> > *"Ẹ̀mí Olúwa ń bẹ lára mi, Nítorí tí ó fi ààmì òróró yàn mí láti wàásù ìhìnrere fún àwọn òtòṣì. Ó ti rán mi wá láti wàásù ìdásílẹ̀ fún àwọn ìgbèkùn, àti ìmúnríran fún àwọn afọ́jú, àti láti jọ̀wọ́ àwọn tí a pa lára lọ́wọ́, láti kéde ọdún ojúrere Olúwa."*
>
> *Ó sì pa ìwé náà dé, ó fi í fún ìránṣẹ́, ó sì jókòó. Gbogbo àwọn tí ó ń bẹ nínú Sinagọgu sì sidion tẹjúmọ́ ọn. Ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í wí fún wọn pé, "Lónìí ìwé mímọ́ yìí ṣẹ ní etí yín."*
>
> *Gbogbo wọn sì jẹ́rìí rẹ̀, háà sì ṣe wọ́n sí ọ̀rọ̀ oore-ọ̀fẹ́ tí ń jáde ní ẹnu rẹ̀, wọ́n sì wí pé, "Ọmọ Josẹfu kọ́ yìí?"*
>
> *Jesu sì wí fún wọn pé, "Lóòótọ́ ni ẹ̀yin ó pa òwe yìí sí mi pé, 'Oníṣègùn, wo ara rẹ sàn! Àwọn ohun tí àwa gbọ́ pé o ti ọwọ́ rẹ ṣe ní Kapernaumu, ṣe é níhìn-ín yìí pẹ̀lú ní ilẹ̀ ara rẹ.'"*
>
> *Ó sì wí pé, "Lóòótọ́ ni mo wí fún un yín, kò sí wòlíì tí a tẹ́wọ́gbà ní ilẹ̀ baba rẹ̀. Ṣùgbọ́n mo wí fún un yín nítòótọ́, opó púpọ̀ ni ó wà ní Israẹli nígbà ọjọ́ wòlíì Elijah, nígbà tí ọ̀run fi sé ní ọdún mẹ́ta òun oṣù mẹ́fà, nígbà tí ìyàn ńlá fi mú ká ilẹ̀ gbogbo; <u>Kò sì sí ẹnìkan nínú wọn tí a rán Elijah sí,</u> bí kò ṣe sí obìnrin opó kan ní Sarefati, ìlú kan ní Sidioni."*
>
> —Luku 4:16-26

Ẹsẹ tí a kà tán yí wáyé lẹ́yìn ìgbà ti a ti dán Jésù wò nínú ijù tí ó sì padà sí ìlú Rẹ̀ ní bí tí a ti rí ìtàn na tí a kọ.

Nítorí ní Násárẹ́tì ni a ti wo Jésù dàgbad,wọ́n ti mọ̀ọ́ òn àti ìdílé rẹ̀ dáada, a sì wó pé yóò ti ka ìwé mímọ́ dáada ní ọ̀pọ̀ ìgbà ní Sínágọ́gù. Nkankan wà tí ó yẹ kí o mọ̀ nípa ẹsẹ Bíbélì tí Jésù kà fún wọn. Onka láti inú ìwe Àísàyà 61:1-2, Ó sì ka tìtí ó fi sọ pé ***"Láti kéde ọdún ìtẹ́wọ́gbà Olúwa"*** ó sì da dúro.

Níbáyií, nkan tí ó dára nípa ibi tí ó ti dá dúro nipé ààrin gbólóhùn ọ̀rọ̀ tí ó ńsọ lo ní, a si mọ̀ pé ó dá dúró níbẹ̀ fún ìdí kan ni.

Ọdún ìtẹ́wọ́gbà Olúwa sì je ọdún Júbílì, ó sì dúró fún ìmúpadàbọ̀sípò ti ìjọba Ọlọ́run ní ìpele ilé ayé. Ohun ni ara ohun tí Mèssáyà ma wá mú padàbọ̀sípò nígbàti ó bá dé. Toríbẹ nígbàtí Jésù dánu dúró ti o wá sọ pé, ***"Lónìí ìwé mímọ́ yìí ṣẹ ní etí yín."*** Ó ńkéde rẹ̀ pé Òn ni Mèssáyà!

Ó sì tẹ̀síwájú ó sì ńsọ àsọtẹ́lẹ̀ àwọn ohun tí wọn ó sọ sị ní ọjọ́ ọ̀la, èyíti ń se pàtàkì jùlọ, "A kò gbà ọ́ gbọ́; fìdirẹ̀ hàn wá," nitori tí wọn kò gbà á gbọ́.

*Jesu sì wí fún wọn pé, "Lóòótọ́ ni ẹ̀yin ó pa òwe yìí sí mi pé, 'Oníṣègùn, wo ara rẹ sàn! Àwọn ohun tí àwa gbọ́ pé o ti ọwọ́ rẹ ṣe ní Kapernaumu, ṣe é níhìn-ín yìí pẹ̀lú ní ilẹ̀ ara rẹ.'"*

Kápérnámù ni olú ìlú ilé iṣẹ́ ìránṣẹ Jésù wà àti pé ibè na ni òpòlọpò iṣẹ́ àmì àti iṣẹ́ ìyanu Rẹ̀ ti wáyé. Ó ńsọ àsọtẹ́lẹ̀ sí wọn pé wọn ó gbó nípa iṣẹ́ àmì àti iṣẹ́ ìyanu ńla tí yóò sẹlẹ̀ ní Kápérnáumù, nígbàtí wọn sì gbọ́ àwọn ǹkan wọ̀nyìí, wọ́n yóò ma sọ pé wá sí ibiyi kí o sì wá se iṣẹ́ yìí kanna ní Násárẹ́tì kí á ba le gbà ọ́ gbọ́. Ohun tó dájú ni, Òn bá wọn wí ní ti ọkàn tí ó le àti àìgbàgbọ́ wọn. Ó mò pé wọ́n kò gba Òn gbọ́, Ó sì mọ̀ pé wọn kò ní gba Òn gbọ́. A mọ̀ pé nítorí tí Ó sọ èyí pé won ó sì tún sọ pé, *"Onísègùn, wo ara rẹ sàn"* wọ́n tọ́kasi ohun ti yóò sọ ní ibití wọn ti ńkàn án mọ́ àgbélébu.

*Àwọn tí ń kọjá lọ sì ń bú u. Wọ́n sì ń mi orí wọn pé: "Ìwọ tí yóò wó tẹmpili, ìwọ tí yóò sì tún un mọ ní ọjọ́ kẹta. Bí ó bá jẹ́ pé*

*Ọmọ Ọlọ́run ni ìwọ, sọ̀kalẹ̀ láti orí igi àgbélébùú, kí ó sì gba ara rẹ̀ là!" Bákan náà àwọn olórí àlùfáà pẹ̀lú àwọn akọ̀wé òfin àti àwọn àgbàgbà Júwonù sì fi í ṣe ẹlẹ́yà. Wọ̀n kẹ́gàn rẹ̀ pé, "Ó gba àwọn ẹlòmíràn là, kò sí lè gba ara rẹ̀. Ìwọ ọba àwọn Israẹli? Sọ̀kalẹ̀ láti orí àgbélébùú nísinsin yìí, àwa yóò sì gbà ọ́ gbọ́.*

—Máttíù 27:39-42

Láti ìbẹ̀rẹ̀ isẹ́ ìránṣẹ́ Rẹ̀ títí dé òpin, Ó ńsọ pé pẹ̀lú ohun gbogbo tí wọn ó gbọ, wọn kò ní gba iṣẹ́ ìfíránsẹ́ Rẹ̀ gbọ́. Ó wá lọ láti jẹ́ kí ìfiránsẹ́ Rẹ̀ le yé wọn ní pa sísọ ìtàn Èlíjàh àti opó fún wọn, níbití Ọlọ́run tí rán Èlíjà jáde lọ sí Ísráẹ̀lì nimtorim àwọn ènìyàn Ìsráẹ̀lì ni irú ọkàn líle tí wọ́n kọ sí ní ìgbàgbọ́. Èyí bí àwọn amòfin wọn nínú dé ibi pé wọ́n mú Jésù jáde láti fẹ́ lọ pa, sùgbọ́n Bíbélì sọ pé Ó yọ́ fi wọ́n sílẹ̀ lọ.

Nísisìyí mo fẹ́ kí o kọ ọ̀rọ̀ kan sílẹ̀ fún mi kí o sì fi sí ibìkan tí wa ti rántí rẹ̀, nítorí òhun ni kọ́kọ́rọ́ sí ìsúná ní ọjọ́ ọ̀la. Kọ ọ̀rọ̀ yìí sílẹ̀ "RÁN." Ó dára bẹ́ẹ̀ " RÁN." Èyí jẹ́ ohun tí ó se pàtàkì!

## <u>RÁN</u>

Mo fẹ́ kọjá sínú Ìwé Àwọn Ọba Kìnní 17:7-16 níbití a o tí rí ohun ìjìnlẹ̀ tó lágbára tí yóò yí ayé rẹ padà pátápáta.

*Ó sì ṣe lẹ́yìn ọjọ́ díẹ̀, odò náà sì gbẹ nítorí kò sí òjò ní ilẹ̀ náà. Ọ̀rọ̀ OLÚWA sì tọ̀ ọ́ wá wí pé: "Lọ nísinsin yìí sí Sarefati ti Sidoni, kí o sì dúró síbẹ̀. Èmi ti pàṣẹ fún obìnrin opó kan níbẹ̀ láti máa bọ́ ọ." Bẹ́ẹ̀ ni ó sì lọ sí Sarefati. Nígbà tí ó sì dé ibodè ìlú náà, obìnrin opó kan ń ṣa igi jọ níbẹ̀. Ó sì ké sí i, ó sì béèrè pé, "Ǹjẹ́ o lè bu omi díẹ̀ fún mi wá nínú ohun èlò kí èmi kí ó lè mu?" Bí ó sì ti ń lọ bù ú wá, ó ké sí i pé, "Jọ̀ ọ́, mú òkèlè oúnjẹ díẹ̀ fún mi wá lọ́wọ́ rẹ̀ Obìnrin opó náà sì dá a lóhùn wí pé,*

*"Bí OLÚWA Ọlọ́run rẹ ti wà, èmi kò ní àkàrà—bí kò ṣe ìkúnwọ́ ìyẹ̀fun nínú ìkòkò àti òróró díẹ̀ nínú kólòbó. Èmi ń ṣa igi díẹ̀ jọ láti kó lọ ilé, kí èmi kí ó sì pèsè rẹ̀ fún mi àti fún ọmọ mi, kí àwa lè jẹ ẹ́—kí a sì kú."*

*Elijah sì wí fún un pé, "Má ṣe bẹ̀rù. Lọ, kí o sì ṣe gẹ́gẹ́ bí o ti wí. Ṣùgbọ́n kọ́kọ́ ṣe àkàrà kékeré kan fún mi nínú rẹ̀ ná, kí o sì mú fún mi wá, lẹ́yìn náà, kí o ṣe tìrẹ àti ti ọmọ rẹ. Nítorí báyìí ni OLÚWA Ọlọ́run Israẹli wí: 'Ìkòkò ìyẹ̀fun náà kì yóò ṣófo, bẹ́ẹ̀ ni kólòbó òróró náà kì yóò gbẹ, títí di ọjọ́ tí OLÚWA yóò rọ òjò sí orí ilẹ̀.'"*

*Ó sì lọ, ó sì ṣe gẹ́gẹ́ bí Elijah ti sọ fún un. Oúnjẹ sì wà fún Elijah àti obìnrin náà àti ilé rẹ̀ ní ojoojúmọ́. Nítorí ìkòkò ìyẹ̀fun náà kò ṣófo, kólòbó òróró náà kò gbẹ, gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ OLÚWA tí ó ti ipa Elijah sọ.*

—Àwọn Ọba Kínní 17:7-16

Jẹ́kí nsọ fún o. Ìyàngbẹ ilẹ̀ ti wà ní ibi gbogbo lọ́wọ́lọ́wọ́, àtipé odò ibitim Elíjà wà na ti ńgbẹ lo. Óní láti lọ sí ibòmíràn láti wá ounjẹ àti omi. Ọlọ́run wá bá a sọ̀rọ̀ àti wi fún un pé "***Lọ nísinsin yìí sí Sarefati ti Sidoni, kí o sì dúró síbẹ̀. Èmi ti pàṣẹ fún obìnrin opó kan níbẹ̀ láti máa bọ́ ọ."*** Sé o mọ pè Sáréfátì kì íse ara ilẹ̀ Kánáánì kì ísi íse ara orílẹ̀-èdè Ísráẹ́lì nígbàna.

Bí Èlíjà ti nsúnmọ́ ìlú nà, wò ó rí obìnrin opó tí ó ńkó igi jọ, ó sì pèé kí ó fún òun ní omi díẹ̀. **"bí ó sì ti ń lọ bù ú wá, ó ké sí i pé, "Jọ̀ ọ́, mú òkèlè oúnjẹ díẹ̀ fún mi wá lọ́wọ́ rẹ̀'"** Obìnrin opó náà sì dá a lóhùn wí pé, èmi kò ní àkàrà,bí kò se èyi tí o kù kí èmi kí ó sì pèsè rẹ̀ fún mi àti fún ọmọ mi.

Sùgbọ́n nígbàna ni wòlíì se ohunkan tí o jẹ́ àjèjì, nkan tí o le rò pé óní nkànkan se ní irum àsìkò yìí. Lọ, kí o sì ṣe gẹ́gẹ́ bí o ti wí. Ṣùgbọ́n kọ́kọ́ ṣe àkàrà kékeré kan fún mi nínú rẹ̀ ná, kí o sì mú fún mi wá, lẹ́yìn náà, kí o ṣe tìrẹ àti ti ọmọ rẹ. Wòó bí yóo ti se gbọ́ létí, ó kọ́kọ́ so fún sáájú pé *"Má ṣe bẹ̀rù.* lẹ́yín ìgbàna ni ó wá pàsẹ àwọn nkan wọ̀nyìí.

*Nítorí báyìí ni OLÚWA Ọlọ́run Israẹli wí: 'Ìkòkò ìyẹ̀fun náà kì yóò ṣófo, bẹ́ẹ̀ ni kólòbó òróró náà kì yóò gbẹ, títí di ọjọ́ tí OLÚWA yóò rọ òjò sí orí ilẹ̀."*

Wow, kínni kó se? Sé kí o gbàágbọ́ ni kí ó sì fi ounjẹ́ tí ọmọ rẹ̀ fẹ́ jẹ gbẹ̀yìn fún un?

*Ó sì lọ, ó sì ṣe gẹ́gẹ́ bí Elijah ti sọ fún un. Oúnjẹ sì wà fún Elijah àti obìnrin náà àti ilé rẹ̀ ní ojoojúmọ́. Nítorí ìkòkò ìyẹ̀fun náà kò ṣófo, kólòbó òróró náà kò gbẹ, gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ OLÚWA tí ó ti ipa Elijah sọ.*

Ó gbàágbọ́, ó sì fiyèsì dáda fún èsì àbájáde—óunjẹ́ wà ní ibi gbogbo fún Èlíjàh àti fún arábìnrin yìí àti ìdílé rẹ̀. Jẹ́ kí ntún ọ̀rọ̀ náà sọ pé, "Óunjẹ wà ní ojojúmọ́ fún iṣẹ́ Ọlọ́run àti óunjẹ fún obìnrin yí àti ìdílé rẹ̀"

A sọ̀rọ̀ ní orí ọ̀rọ̀ tí ó kọjá nípa ìbẹ̀rù láti se fífúnni, pé ohun tó bá kù kò ní tó se nkàn tó bá fẹ́ se ti ó bá ti fi fún iṣẹ́ Ọlọ́run. Bí ó ti se rí báyìí, tí wà sì tún máa rí bẹ̀ nígbogbo ìgbà, pé kò le sẹlẹ̀ bẹ́ẹ̀!

Ó yá jẹ́ kín bi ọ́ léèrè ìbéèrè kan, Sé o ná opó nà ní ohun kankan láti fún wòlíì ní gbogbo óunjẹ tí o ní? Rárá, kò na ní ǹkankan. Ó tún gba ayé rẹ̀ là ni.

Níbáyí, kín tó lọ sínú ìjíròrò wa tí ńse ọ̀rọ̀ lórí RÁN, mo tún fẹ́ bèrè ìbéèrè kan síi. Kínni ìdí tí wòlíì fi ní kí *ó kọ́kọ́* se àkàrà tí òun ná? Kí se papọ̀ *pẹ̀lú* tirẹ̀ bíkòse *ní ọ̀tọ̀tọ̀.* O tún sọ fún pé kí ó kọ́kọ́ gbé ti òun wá ná *sáájú* kí ó tó lọ bẹ̀rẹ̀ sí se tiẹ̀. (Rántí, o fẹ́ jẹ́ onímọ̀ ìjìnlẹ̀ ti ẹ̀mí àti máa bèrè ìbéèrè.)

Gbogbo àwọn ìtàn wọ̀nyìí ńfi àwọn ohun ìjìnlẹ̀ tí ó se kókó sínú òfin ti Ìjọba àti bí ó ti se ńsisẹ́. Sé ebi ní ó wá ńpa Èlíjàh dé ibi pé kò ní le dúró tí yóò fi se ounjẹ gbogbo wọn papọ̀ tán? Wòlíì mọ̀ pé tí ó bá kọ́kọ́ fún òun ní oúnjẹ, sáájú kí ó tó se tírẹ̀, iṣé rẹ̀ ni yóò mú gbogbo ìyẹ̀fun tí ó nílò àti òróró wá bí ètọ́ lábẹ́ òfin ti Ìjọba Ọlọ́run àti àkànse iṣẹ́ rẹ. Jẹ́ ki ntún sọ èyí lẹ́ẹ̀kansi.

Nígbàtí ó fún wòlíì (Àkànse iṣẹ́ Ọlọ́run) ní àkàrà àkọ́kọ́, òróró àti ìyẹ̀fun rẹ̀ yí ìjọba padà. Wọn wá sí abẹ́ ìsàkóso ti Ìjọba ti Ọlọ́run. Nígbàna sì ni Ọlórun tó le mú kí ìyèfun àti òróró nà pọ̀si ní ìlọ́po.

Wà rí pé ìlànà yí nà sisẹ́ nínú isẹ́ ìránsẹ́ Jésù nà nígbàtí ó bọ́ àwọn ẹgbẹ̀rún máàrún pẹ̀lú ìsù àkàrà máàrún àti ẹja wẹ́wẹ́ méjì.

Tí ó bá rántí ìtàn na, Jésù sọ fún àwọn ọmọ-ẹ̀hìn láti lọ wo ohun tí wọ́n ní. Wọ́n sì padà wá sọ fún un pé ìsù àkàrà máàrún àti ẹja wẹ́wẹ́ méjì ni ó wà. Jésù sọ fún àwọn ọmọ-ẹ̀hìn rẹ̀ pé kí wọ́n lọ mú wá fún òun. Bíbélì se àkọsílẹ̀ rẹ̀ pé Ó sì mú wọn ó sì súre síi ó sì fún àwọn ọmọ-ẹ̀hìn rè padà.

Mo mọ̀ ṕe Jésù kò se ǹkan tó ní se pẹ̀lú èsìn, kí wálódé tí o fi se nkán tó se yìí?

Oní láti se bẹ́ẹ̀ tí kò bá seé àkàrà àti ẹja yìí kò bá má to láti pín. Sé o wá ríi, ìsù àkàrà máàrún àti ẹja wẹ́wẹ́ méjì yí sì wà lábẹ́ ìjọba tí ènìyàn nígbàna. Ọlọ́run kò ní le se ohun kóhun lábẹ́ òfin pẹ̀lú wọn. Sùgbọ́n nígbàtí wọ́n ti kó o lé Jésù lọ́wọ́ tí o sì ti súre síi, wọ́n ti wá sí abẹ́ ìjinlẹ́ ti Ìjọba Ọlọ́run. Níbẹ̀ ati nígbàna ni ìsù àkàra àti ẹja na sì le pọ̀si.

A le rí ìlànà òfin yí nà nínú Luḱu`orí kaar̀uǹ nibití Pétérù, Jákọ́bù àti Jòhánnù tí wọ́n ti ńfi gbogbo òru wá ẹja tí wọn kò sì rí ẹja kankan pa. Jésù wá yá ọkọ̀ Pétérù, Jésu tìí sí etí odó ó si ńwàásù fún gbogbo ìjọ ènìyàn lẹ́yìn ìgbà tí ó ti sọ fún Pétérù láti sọ àwọ̀n rẹ̀ sínú ibum láti kó ẹja.

Bí o bá rántí ọkọ̀ méjì ni wọ́n kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja tí ọkọ̀ sì fẹ́ rìi. Nígbàtí Jésù yá ọkọ̀ ojú omi na tán, ó sì nya ọkọ̀ ẹja sisẹ́ láti máa wàaśù láti ọjọ́ nà lọ. Ní kété tí Ó gba iṣẹ́, gbogbo rẹ̀ bọ sí abẹ́ ìlànà ìsàkóso ti Ìjọba Ọlọrun. Èyí ni ó sọ di èyí tí ó ni ́ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin fún ọ̀run láti le fi ọ̀rọ̀ ìmọ̀ ránsẹ́ sí Jésù láti sọ ibití ẹja wà, tí íse mímú eja ńlá.(Mo má ńsọ nígbogbo ìgbà pé ẹnikẹ́ni ni ó le pa ẹja tí Jésù bá ti sọ fún un ibití wọn wà láti ŕi wọn mú. Ìlànà òfin na ni wà máa mú lò nígbà tí ó bá ti fifún iṣẹ́ àkànse ti Ọlọrun).

Níbayí, kín padà sínu ìtàn ti Èlíjàh tí a ńsọ, obìnrin opó yìí jẹ́ alábásisẹpò pẹ̀lú Èlíjàh àti iṣẹ́ rẹ̀ ó sì gba irú èrè kanna tí ó ní. Ìpèsè wà fún Èlíjàh ÀTI obìnrin opó yií àti ìdílé rẹ̀. Sé o ti ri?

Má sì tún sòrò sí lórí ìlànà òfin tí ó bá yá nínú ìwé yií, sùgbọ́n mo lọ sí ibi kókó ìtàn yìí tí ńse RÁN.

Ẹ jẹ́ kí á gbéyẹ̀wò. Ọlọ́run fún Èlíjàh ní iṣẹ́ láti se. Ó sì nílò ìpèsè láti le se iṣẹ́ nà tí Ó fẹ́ se. A mọ̀ pé wòlíì ni Èlíjàh ńse, Ó má ńgbé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run lọ sí ibikíbi tí Ọlọ́run bá ran lọ. Sùgbọ́n Ọlọrun fẹ́ kí iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́ síse, nítorí rẹ̀ ni ó se má ní kí àwọn *ènìyàn* dásíi.

Níbiyí, Ọlọ́run kò ri opó kan ní Ísráẹ́lì tí ó le ní ìgbàgbọ́ làti gbọ́ràn si lẹ́nu. Ọlọrun sì mọ ohun tí ó fẹ́ se, sùgbọ́n ó ní láti ní ẹnìkan tí yóò ba se àdéhun papọ̀ pẹ̀lú ọ̀run láti jẹ́ kí ó di ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin fún Un láti mú ìpèsè tí Èlíjàh nílò wá fún un.

Rántí, kò sí ounjẹ nibikibi. Àwọn ènìyàn ńkú níbigbogbo. Kì íse ọ̀rọ̀ pé mo kàn rí oúnjẹ nibìkan, tàbí pé mo ńlọ sí ọjà, nítorí kò tí ẹ̀ sí oúnjẹ níbikíbi. Ìpèsè fún Èlíjàh ní láti wà nipa Ẹ̀mí Ọlọ́run.

Níwọ̀n ìgbàtí kò sí ẹnikankan ní Ísráẹ́lì tí ó ní ìgbàgbọ́ láti gbà àgbọ́, Ọlọ́run wà ni láti jáde kúrò ní Ísráẹ́lì lọ sí orílẹ̀-èdè míràn níbítí ó ti rí opó tí ó ní ọkàn ìgbàgbọ́. Bí a ti sọ sáájú pé a rán Èlíjàh sí opó yìí nítorí ti Ọlọ́run mọ̀ pe yóò gba Òn gbọ́.

Nípa fífi Ọlọ́run se àkọ́kọ́ àti gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ Olúwa sí iṣẹ́ Ọ́lọ́run, ó sètọjú Èlíjàh àti ìdìlé rẹ̀ nígbogbo ìgbà ti ìyàn náà mú.

Toríbẹ kókó inú ìtàn ná ńiyìí…

Nígbàtí Ọlọ̀run bá ní ohunkan láti se, ó má wo inú ayé láti wá ẹnikan tí Òn le gbẹ́kẹ̀le, ẹníti yóò gbọ́ràn sí lẹ́nu àti se àwọn nkan tí Ó bá ní lérò láti se. Ó sì tún nílò àwọn ènìyàn tí yóò náwó sí àwọn ohun tí ó fẹ́ se. Toribẹ̀ , jẹ́kí nsọ kí ó ye ọ. Tí o bá fẹ́ ní èrò tí ó tóbí, tí o bá fẹ́ kí Ọlọ́run gbé àwọn isẹ́ oko òwò ńla fúń ọ oní láti kún ojú òsùnwọn! Ọlọ́run mọ ọkàn rẹ, àtipé ó sì nwo gbogbo inú ayé láti rí ẹnití o le gbẹ́kẹ̀le àti gbé isẹ́ Rẹ̀ lé lọ́wọ́. Ó nwo láti rí ẹniti Ó le fọkàntẹ̀ tí yóò lawọ́ sí isẹ́ Rẹ̀. Yóò wa fi ọ̀nà tí yóò gbà fi kó owó nà jọ èyití ó nílò ránsẹ́ sí irú ẹni nà. sé o ti rii?

Rántí a RÁN ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sí opó yí ó sì gbà ayé rẹ̀ là!

Mo rántí ìgbàtí ọ̀rọ Ọlọ́run tọ̀ mi wá tí óní kin jádè láti lọ bẹ̀rẹ̀ isẹ́ tarami pẹ̀lú ohun titun àti àsẹ, mo sé e ó sì gba ayé mi là.

Ọlọ́run ńwá àwọn tí yóò ní ọkàn ìgbọràn láti nawọ́ sí àwọn isẹ́ Rẹ̀!

Jẹ́ki á lọ gbé ìlànà òfin tí a rí nínú ìtàn yìí wò.

1. Ọlọ́run ní àwọn isẹ́ àkànse tí ó fẹ́ se lórí ilẹ̀ ayé tí ó sì fẹ́ see parí.
2. Gbogbo isẹ́ yìí ni ó nílò àwọn ènìyàn.
3. Gbogbo isẹ́ nà ní ó nílò níná owó.
4. Ọlọ́run nwo orílẹ̀ ayé láti rí àwọn ẹnití yóò se ìnáwó lórí isẹ́ Rẹ̀.
5. Ọlọ́run sí nwo orílẹ̀ ayé fún àwọn tí yóò sètò ìnáwo lórí isẹ́ Rẹ̀.
6. Nígbàtí a bá rí àwọn isẹ Ọlórun, á wá nfún ọ̀run ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin, kì íse láti lòwá nìkan láti náwó sí isẹ́ tí Ọlọ́run nìkan ni bíkòse kí àkúnwọ́sílẹ̀ rẹ sì wá ayé tí wá náa pẹ̀lú ri bákanna.

Kò le ná ọ níkankan láti jẹ́ ẹniti ó lawọ́ onínúrere ènìyàn! Mo sọ fún ìjọ mi, pé Màá sọ pé "Bẹ́ènì nígbà gbogbo."

ORI KẸRIN

# OWO TANI O JE?

Njẹ̀ o tì lẹ̀ rò rí pé àwọn owó kan wà lọ́wọ́ rẹ báyii tí kì íse tìrẹ?

Mo mọ̀ pé bí ọ̀rọ̀ wèrè ni létí rẹ, sé o mọ̀ pé Ọlọ́run le kó owó sí ọ lọ́wọ́ fún àwọn nkan míràn?

Mo mọ̀, Mo mọ̀ o le má rò àti fojú inú wò ó lọ́nà yí, sùgbọ́n ó yẹ kí o se bẹ nítorí ó jẹ́ kọ́kọ́rọ́ kan sí pípọ̀si nínú ayé rẹ̀.

Ronú sí ǹkan tí mo ńsọ. À ti ńsọ̀ro nípa nínáwó sí isẹ́ àkànse ti Ọlọ́run, àbí? A sì sọ pé Ọlọ́run nwo orí ilẹ̀ láti rí ènìyàn tí ọkàn re wà fún Ìjọba àti fe láti má náwó sí àwọn isẹ́ Ọlórun. À mọ wípé owó wà lọ́wọ́ àwọn ènìyàn, tí Ọlọ́run bá sì fe sisẹ rẹ̀, óní láti jẹ́ kí owó wá sí ọwọ́ àwọn ènìyàn tí ó nífẹ̀ láti fí owó nà sílẹ̀ tí wọn lawọ́ sí Òn àti àwọn ènìyàn Rẹ̀.

Toríbẹ̀, kín ni ó wà ní ọwọ́ rẹ? Sé tí o bá wo ohun tí o ní se o mọ̀ pé Ọlọmrun le fí sí ọ lọ́wọ́ fún àwọn ẹlòmíràn? Tàbí pé ó le mu wá fún ọ láti lò fún àkànse isẹ́ tí ó fé se parí?

Beèni, lábẹ̀ òfin, ohun tí ó ní tìrẹ ni àti pé ìwọ ni o le pinnu nkan tí o fe fi se. Sùgbon ti Ọlọ́run yóò bá fi owó sí àwọn ènìyàn lọ́wọ́, Ẹ̀mí fẹ́ wà láàrin àwọn tí ó bam fọwọ́sí. Sé ìwọ o fẹ́ bẹ̀?

> *Ǹjẹ́ ẹni tí ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ, yóò fi irúgbìn fún un yín, yóò sì sọ ọ́ di púpọ̀, yóò sì mú èso òdodo yín bí sí i. Bẹ̀ẹ̀ ni a ó sọ yín di ọlọ́rọ̀ nínú ohun gbogbo, fún ìlawọ́ yín gbogbo tí ń ṣiṣẹ́ ọpẹ́ sí Ọlọ́run nípa wa.*
>
> —2 Korinti 9:10-11

A ti wo ẹsẹ ìwé mímọ́ yìí tẹ́lẹ̀, sùgbọ́n ǹkankan wà níbíyìí ti mo fẹ́ kí o túто wò. Ẹsẹ 10 sọ pé Ọlọ́run *pèsè* irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà

fún oúnjẹ.

Ronú nípa ohun tí ó sọ: Ọlọ́run ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ. Àkàrà fún óunjẹ dúró fún ohun gbogbo tí o nílò ìdílé rẹ láti máa gbé ìgbé ayé ìyè lọ́pọ̀lọpọ̀ tí Ọlọ́run fi fún ọ. Sùgbọ́n Ó fi *irúgbìn fún afurúgbìn.*

Sé o ti gbin nkàn sínú ọgbà rí tàbí kí o gbin koríko sí àyíká ilé rẹ rí? Wa bẹ̀rẹ̀ sí ní fi irúgbìn bọ inú ilẹ̀, bí o sì ti nfúrúgbìn, wà má gba àwọn èso míràn kún ọwọ́ rẹ bí o ti se ńgbìn èyítí ó wà lọ́wọ́ re tẹ́lẹ̀ tán. Ó dájú pé bí o ti ńgbin ọ̀kan tán ni òmíràn ńdé ọwọ́ rẹ, ọwọ́ rẹ wá kún fún irúgbìn tí o ní láti gbìn bákanna. Nínú gbólóhùn ọ̀rọ̀ yií, *Ọlọ́run ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn*, sí ní àkọsílẹ̀ kanna, tí ó túmò si Ọlọ́run ńfi irúgbìn fún ẹnití ó fẹ lọ láti gbìn.

## ỌLỌ́RUN Ń FI IRÚGBÌN FÚN ẸNITÍ Ó FÚNRÚGBÌN!

Páùlù tún tẹ̀síwájú ó sọ pé Ọlọ́run fún wa ní àkàrà tí a nílò bákanna, bẹ́ẹ̀ni, sùgbọ́n nínú gbíngbin ni ó ńsọrọ̀ lé níbiyìí ati ipa tóní lórí ayé wa àti bákanna àwọn tí a ń náwó sí. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ tẹ́lẹ̀, ó mú kí ọkàn àwọn ènìyàn fà sí Ọlọ́run.

Pẹ̀lú èyí nínú ọkàn, mo lérò wípé gbogbo wa ní a o gbà pé Ọlọ́run fé gbin irúgbìn ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ bí ó ti seése kí o ba le kó ìkórè ńlá. Toribẹ̀, tí ó bá jẹ́ pé ìwọ ni Ọlọ́run, tani wà fi irúgbìn fún? Sé ẹniti ó ya ọ̀lẹ ni tí kò sì nsúnmọ́ ibití wọ́n ti ńfúnrúgbìn tàbí ẹnití ó lákitiyan tí ó ńfúnrúgbìn? Mo lérò wípé ìdáhùn ti farahàn.

Bí a ti jẹ́ olótìtọ pẹ̀lú ohun tí a ní, Ọlọ́run sọ pé Òn yóò mú kí irúgbìn wá pọ̀si kí a ba le gbin irúgbìn tó pọ̀ kí á sì le ní ipa tótóbi lórí ilẹ̀ ayé fún Ìjọba Rẹ̀.

Sé o kíyèsí tí Páùlù sọ pé bí ó ti se ńfúnrúgbìn àti kórè, bẹ́ ni yóò so èso yín di pípọ̀ si,tí yóò si mú yín láti máa lawọ́ ní ìgbà gbogbo? Tí èyí bá jẹ́ òtítọ́ (tí ó sì jẹ́ pé bẹ́ẹ̀ni), a jẹ́ pé nígbàna àká irúgbìn rẹ̀ na ni owó tí óní lọ́wọ́ bayí kí ànfàní fún lílawọ́ rẹ ba le farahàn. Àká irúgbìn rẹ̀ ní láti wà nílẹ̀ kí ó tó lé má jẹ́ ẹnití ó lawọ́.

Lẹ́ẹ̀kansii, ohun tí, mo ńsọ ni pé owó tí ó kódání yẹn kì íse tirẹ̀. Ara èyí tí Ọlọ́run fi fún ọ láti fúrúgbìn ni. Àyíká á ńgbìn àti kóre yín ńsàn lọ ni.

A ó gbìn, a ó sì ká; bí a sì ti tẹ̀síwájú láti se bẹ, níwọ̀n ìgbà tí a kò bá ti jẹ irúgbìn wa, ìkórè wa yóò ma pọ̀si ni, yó sì wá fún wa ní agbára láti máa lawọ́ tàbí se inúrere síi.

Bẹ́ẹ̀ni, nígbàtí ebi bá npa ọ́ tí o sì nílò óunjẹ, wà mú lára irúgbìn ti oko-òwò rẹ ohun tí o nílò bákana. Bí irúgbìn oko-òwò rẹ ti ń́pọ̀si, agbára láti le mú àkàrà nínú rẹ̀ yóò maa pọ̀si bákanna.

Sùgbọn mo fẹ́ wàá jinlẹ̀ díẹ̀ si ní inú irú èrò ọkàn yií.

Jẹ kin sọ kókó idí tí Ọlọ́run se fi irúgbìn Rẹ̀ fún ẹnití óní ọkàn láti fúnrúgbìn, kí íse ẹnítí ó kàn le tún ròò wò pé bóyá ní ọjọ́ míràn. Ó fi fún afúnrúgbìn.

Torínà ìbéèrè na nì yìí: Sé o fẹ́ má gbé ayé kí o máa kó owó *ara* rẹ nìkan dání, tàbí o fẹ́ gbé ayé ẹnití ó ńkó owó tí ara rẹ̀ àti owó ti Ọlọ́run dání?

Jákọ́bù àti Ella wá sí ilé ìjọsìn wa nítorí tí wọn ńgbọ ohun tí wọn ò gbọ́ rí ní àdúgbò Amish níbití wọ́n gbé dàgbà. Àwọn èròǹgbà ti ìjọba gbogbo ní ó jẹ́ titun sí wọn, wọn sì jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọmọ ilé ìwé ńlá ti Ìjọba. Wọ́n tẹ́tí síi léraléra sí àwọn ọ̀rọ̀ ìfiránṣẹ́ tí a kọ lórí ìgbé ayé ti Ìjọba ní Faith Life Church.

**Sé O FẸ́ MÁA GBÉ AYÉ KÍKÓ OWÓ TI ARA RẸ NÌKAN DÁNÍ TÀBÍ ÀTI KÓ OWÓ ỌLỌ́RUN NÁÀ DÁNÍ?**

Ní ọjọ́ kan, Jákọ́bù sọ fún Olúwa pé òun ńgbọ́ gbogbo ìtàn wọ̀nyìí láti ọ̀dọ̀ àwọn ẹlòmíràn nípa bí Ìjọba tí nse àwọn ohun ńlá ninú ayé wọn, òun nà sí fẹ́ láti ní irú àwọn ẹ̀rí yìí kan nà. Ó wá pínnú pé òun yóò sì dán òfin Ìjọba tí ó ti gbọ́ wò. Wọn lọ fún ìsimi ránpẹ́ wọn sí lo gbogbo àsìkò wọn láti tẹ́tísí ọ̀rọ̀ ìfiránsẹ́ tí ó níse pẹ̀lú ìpín méjì, tí mo ńkọ́ lọ́wọ́ ní ìgbàna. Ìwé mi, *Yíyí Ètò Ìsúná Rẹ Padà: Agbára Tí Ìsinmi* sì sẹ̀sẹ̀ jáde ni, mó sì ńse ìdánílẹ́kọ fún wọn láti inú ìwé nà.

Wọ́n wá pínnu pé àwọn yóò rí ara àwọn sínu ọ̀rọ̀ nà pátápátá sáájú kí àwọn to gbin irúgbìn. Wọ́n pinnu pé àwọn yóò gbin irúgbìn fún ti ìkórè ọ̀kẹ́-máàrún pọ̀ún, tí wọ́n nílò láti fi se àtúnse àti àwọn nkan míràn tí gbogbo ẹbí wọn fẹ́ se pẹ̀lú èyí tí àwọn ọmọ wọn na ni. Wọn kò mọ ibití owó nà yóò ti wá, sùgbọ́n wọn ti ńkọ́ nípa Ìjọba tipẹ́ nígbàti wọn wá ri pé ìgbàgbọ àwọn titó gbé.

Ní àsìkò yí Jákọ̀bù ní ilé isẹ ti ara rẹ̀ tí o ntún ọkọ̀ se. Bí ó ti se ń jáde lọ sí ibisẹ́, kò pé tí wọn fúnrúgbìn ọ̀kẹ́-máàrún pọ̀ùn, ó sọ fún Ella pé lẹ́yìn ìgbàtí wọ́n ti kà nípa ìpín méjì, óní òun fẹ́ kí àwọn gbàgbọ́ fún ìpìn méjì lórí irúgbìn wọn.Óní òun gbàgbọ́ pé ọ̀kẹ́ mẹ́wa pọ̀ùn ni àwọn o fi rí gbà padà. Ella ní ó dẹ́rùba òun, sùgbọ́n òun ní láti máa lọ pẹ̀lú ọkọ rẹ̀. Bí ó ti se ńjáde lọ ní ẹnu lẹ̀kùn, óní "Ó dára, ọ̀kẹ́- mẹ́wa pọ̀ùn."

Ọjọ́ nà jẹ́ ọjọ míràn ní ilé ìtajà wọn. Ọ̀kan lára àwọn onibárà Jákọ̀bù wá láti tún ǹkanse, bí ó ti ko. gbogbo ohun ti o fẹ́ rà tán, oníbarà rẹ jókòó nínú ọfísi Jákọ̀bù ó si sọ fún bí àwọn màálù rẹ̀ ti se ńdàáláàmú. Wọ́n ti wó ọgbà ilé rẹ̀ wọ́n titú jáde. Òun ìní tirẹ̀ ni ó bá oko ọba pàalà sínú aginjù, àwọn màálù rẹ ti wọgbó wọn sì nrìn kákìri ibiti wọ́n fẹ́. Àgbàlagbà ní oníbarà Jákóbù yìí, tí ó sìn sọ fún pé òun ti dàgbà ju kí òun tún máa se wàhálà à ńlé màalù kiri báyìí, ọ̀rọ̀ wọn tisú òun. Nkan tí ó wá tún sọ dẹ̀rùbà Jákọ̀bù tí ó tún fi ńbí ara rẹ̀ léèrè pé sé òun sì gbọ́ ohun tí ọ̀rẹ́ òun sọ dáadáa.

Ọ̀re rẹ̀ sọ wípé, Ọ̀rọ̀ àwọn màálù yìí tisú mi mi ò ní nkan se pẹ̀lú wọn mọ́, torínà ni mo se fún ọ ní gbogbo àwọn màálu yìí loni. Láti òní lọ, wọ́n ti di tìrẹ." Jákọ̀bù ko mọ nkan tí yóo sọ. Kò ní ilẹ̀. Inú ilú ni ó ńgbé lórí saare ilẹ̀ kékeré kan, isẹ́ mẹkálíkì ni ó ńse. Síbẹ̀ Amish ni ó gbé dàgbà tí ó sì ti gbé rí láàrin àwọn màálù, sùgbọ́n ọdún nà tipẹ́. Ó fẹ sọ pé rárá oseun nígbàtí ó rántí irúgbìn rẹ̀. Bóyá nkankan wà tí o ní láti gbéyẹ̀wò.

Lẹ́yìn tí ó ti bí ọ̀rẹ́ rẹ̀ léèrè síwájú sim, ó wá ripé màalù mẹ́tàlélógún Black Angus àti àwọn ẹsin mẹ́ta ni a ńsọ̀rọ̀ lé lórí. Jákọ̀bù wá rántí pé òun àti ẹnìkan ti sọrọ̀ nígbàkan pé àwon ńwá àwọn agbo ẹran tí àwọn fẹ́ láti rà. Kì íse pé wọ́n fẹ ra ní díẹ̀díẹ̀ bíkòse pé agbo ẹran ẹlòmíràn ni wọ́n fé láti rà. Jákọ̀bù pè wọn lórí ago. Ẹni na sì sọ pé ó wu òun láti rà. Jákọ̀bù wá bèrè pé èló ni yóò san fún àwọn ẹran yìí arákùnrin na sí ròó fún bí ìsẹ́jú díẹ̀ ó sì dáhùn pé, "Ha, bóyá bí ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ̀ùn."

Jákọ̀bù fẹ́ le má gba ohun ti ó ńgbọ́ gbó. Àwọn nkan yí sẹlẹ̀ lẹ́yìn tí ó kúrò nílé ní ọjọ́ nà tí ó sì ti sọ fún Ella pé ìpín méjì ni láti ọ̀dọ̀ Ẹ̀mí Mímọ́. Ó sọ fún mi pé isẹ́ ńlá ni láti le rí màalu gbá mú ati gbé sínú ọkọ̀ dé ilé wọn titun. Sùgbọ́n ó bá wọn se Jákọ̀bù wá sọ fún mí pé ó wá òun lójú pé Ìjọba ti Ọlorun le se ohunkóhun òun kò sì ní gbé òdiwọ̀n lé agbára tí òun le se mọ́.

Ní ìgbàtí ó dé ilé ni ọjọ́ nà tí ó sọ fún Ella nípa àwọn màalu, ó ní ohun ìyàlẹ́nu ní ó jẹ́ fún un. Tí ó bá má bèrè lọ́wọ́ Jákọ́bù àti Ella nípa ore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run, Ó ní láti ní àsìkò tí wa lò pèlú wọn torí wọ́n ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun tí wọ́n ó sọ.

Àpẹẹrẹ ńlá tí Ẹ̀mí Mímọ́ ni èyí tí ó fi hàn ènìyàn ibití wà ti ká ìkórè nípa nínawó sí Ọlọ́run. Níwọ̀n tí a bá ti fúnrúgbìn, a sì le rántí ohun tí Ẹ̀mí Mímọ́ fi hàn wá le dàbí, torí kòsí gbólóhùn tótún dára tí a le lò, *ọ̀rọ̀ wèrè*! Mo ńsọ pé kò sí bí Jákọ́bù ti se leronú kan irú èrò yìí pẹ̀lú ìwé àti pẹ́nsù rẹ̀ tí ó nsisẹ́ rẹ̀ lọ tí ó sì le lo ọpọlọ rẹ̀ láti se nkan yìí.

Jẹ kí á wo Pétérù fún àpẹẹrẹ. Mo mọ̀ dájú pé èrò rẹ̀ ti ó gajùlọ kò le dé ibi pé kí ó lọ wo ẹnu ẹja láti rí owó tí yóò fi san owó orí, tàbí pé Olùkọ́ni yóò lo. sí etí òkun láti le sọ fún un ibití om yẹ tàbim tọ́ fún láti ju àwọ̀n rẹ̀ sí láti mú ẹja.

Wo ìgbàtí èmi àti Drenda nà wà lóko gbèsè fún bí ọdún mẹsán nínú ìdàámú àti wàhálà. Ẹ̀rò pé ní ọjọ́ kan a ó ní ilé isẹ́ ti ara wa a ó ma ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́ láti jáde kúrò lóko gbèsè, tàbí èyí tí ó tún yanilẹ́nu pé a ó tumn má kéde lomrí tẹlifisiọ́nù tí ó nsisẹ́ ní gbogbo ìgbà tí à pè ní *Yíyanjú ọ̀rọ̀ owó ná*, kò nim seése.

O kò ní le díwọ̀n Ọlọ́run laílaí.

Toríbẹ̀, jẹ́ kí á gbéyẹ̀wò, àti rántí pé Ọlọ́run nfún irumgbìn fún a fúnrúgbìn—ẹnití ó ńfúnrúgbìn àti ẹnití ó fẹ́ láti fúnrúgbìn!.

Ẹ jẹ́ kí á tẹ̀síwájú. Mo fẹ́ lọ se àgbéyẹ̀wò òwe tí mo lérò pé ó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn òwe tí Jésù  kọ́ nípa pé Ọlọ́run nsisẹ́ pẹ̀lú àwọn ènìyàn àti bí wọ́n ti se le gbọdọ̀ yẹ fún lílò.  Èyí yóò mú ọ dúró àti ronú.

> *Ó sì wí fún àwọn ọmọ-ẹ̀yìn rẹ̀ pẹ̀lú pé, "Ọkùnrin ọlọ́rọ̀ kan wà, tí ó ní ìríjú kan; òun náà ni wọ́n fi sùn ún pé, ó ti ń fi ohun ìní rẹ̀ ṣòfò. Nígbà tí ó sì pè é, ó wí fún un pé, 'Èéṣe tí èmi fi ń gbọ́ èyí sí ọ? Ṣírò iṣẹ́ ìríjú rẹ; nítorí ìwọ kò lè ṣe ìríjú mi mọ́."*
>
> *"Ìríjú náà sì wí nínú ara rẹ̀ pé, 'Èwo ni èmi ó ṣe? Nítorí tí olúwa mi gba iṣẹ́ ìríjú lọ́wọ́ mi: èmi kò le ṣiṣẹ́ oko, bẹ́ẹ̀ ni ojú ń tì mí láti ṣagbe. Mo mọ èyí tí èmi yóò ṣe, nígbà tí a bá mú mi kúrò níbi iṣẹ́ ìríjú, kí àwọn ènìyàn le gbà mí sínú ilé wọn."*
>
> *"Ó sì pe àwọn ajigbèsè olúwa rẹ̀ sọ́dọ̀ rẹ̀, ó sì wí fún èkínní*

*pé, 'Èló ni ìwọ jẹ olúwa mi?"*

*"Ó sì wí pé, 'Ọgọ́rùn-ún òṣùwọ̀n òróró."*

*"Ó sì wí fún un pé, 'Mú ìwé rẹ, sì jókòó nísinsin yìí, kí o sì kọ àádọ́ta.' "Nígbà náà ni ó sì bi ẹnìkejì pé, 'Èló ni ìwọ jẹ?"*

*"Òun sì wí pé, 'Ọgọ́rùn-ún òṣùwọ̀n alikama."*

*"Ó sì wí fún un pé, 'Mú ìwé rẹ, kí o sì kọ ọgọ́rin "Olúwa rẹ̀ sì yin aláìṣòótọ́ ìríjú náà, nítorí tí ó fi ọgbọ́n ṣe é: àwọn ọmọ ayé yìí sá à gbọ́n ní Ìran wọn ju àwọn ọmọ ìmọ́lẹ̀ lọ. Èmi sì wí fún yín, ẹ fi ọrọ̀ ayé yìí yan ọ̀rẹ́ fún ara yín pé, nígbà tí o ba lọ, kí wọn kí ó le gbà yín sí ibùjókòó wọn títí ayé.*

*"Ẹni tí ó bá ṣe olóòtítọ́ nínú ohun kínkínní, ó ṣe olóòtítọ́ ní púpọ̀ pẹ̀lú: ẹni tí ó bá sì ṣe aláìṣòótọ́ ní ohun kínkínní, ó ṣe aláìṣòótọ́ ní ohun púpọ̀ pẹ̀lú. Ǹjẹ́ bí ẹ̀yin kò bá ti jẹ́ olóòtítọ́ nínú ọrọ̀ ayé "Olúwa rẹ̀ sì yin aláìṣòótọ́ ìríjú náà, nítorí tí ó fi ọgbọ́n ṣe é: àwọn ọmọ ayé yìí sá à gbọ́n ní Ìran wọn ju àwọn ọmọ ìmọ́lẹ̀ lọ. Ǹjẹ́ bí ẹ̀yin kò bá ti jẹ́ olóòtítọ́ nínú ọrọ̀ ayé yìí, ta ni yóò fi ọ̀rọ̀ tòótọ́ fún yín? Bí ẹ̀yin kò bá sì ti jẹ́ olóòtítọ́ nínú ohun tí í ṣe ti ẹlòmíràn, ta ni yóò fún yín ní ohun tí í ṣe ti ẹ̀yin tìkára yín?*

*"Kò sì í ẹnìkan tí ó lè sin ọ̀gá méjì. Òun yóò yà kórìíra ọ̀kan tí yóò fẹ́ràn èkejì, tàbí kí ó fi ara mọ́ ọ̀kan kí ó sì yan èkejì ní ìpọ̀sí. Ẹ̀yin kò lè sin Ọlọ́run àti owó papọ̀."*

*Àwọn Farisi, tí wọ́n ní ojúkòkòrò sì gbọ́ gbogbo nǹkan wọ̀nyíwọ̀n sì yọ ṣùtì sí i. Ó sì wí fún wọn pé, "Ẹ̀yin ni àwọn tí ń dá àre fún ara yín níwájú ènìyàn; ṣùgbọ́n Ọlọ́run mọ ọkàn yín: nítorí ohun ti a gbéga lójú ènìyàn, ìríra ni níwájú Ọlọ́run.*

—Luku 16 :1-15

Ọ̀pọ̀ nkan ni ó wà nínú òwe yìí láti yẹ̀wò. Àkọ́kọ́, a rí Okùnrin ọlọ́rọ̀ kan tí ó lọ fi ìrújú kan sí ìsàkóso gbogbo isẹ́ rẹ̀, tí ó sì jẹ́ wípé ìríjú yìí ńfi ohnu ìní ọlọ́rọ̀ yìí sòfò tí ó mú kí ó má yẹ láti tẹ̀síwájú ní ẹnu isẹ́ nà bí ìríjú mọ́. Ní kété tí ó ti mọ̀ pé òun ti pàdánù isẹ́ rẹ̀, ó tètè pe àwọn tí ó jẹ́ olúwa rẹ̀ ní owó ó sì sọ fún wọn láti san owó tí wọn jẹ pẹ̀lú ẹ̀dínwó ńlá, ìgbàmíràn ìdá àádọ́ta owó tí wọ́n jẹ tí wọ́n bá le sán an ní kíákíá.

Níbayìí, lóòtítọ́, ẹniti ó ní isẹ́ nà kò mọ̀ nkan tí ìríjú rẹ̀ ńse. Sùgbọ́n ìríjú aláìsòótọ́ yí lérò pé tí òun bá fún àwọn ènìyàn ní ànfàní yìí wọn o fi

ojúrere wo òun ìgbàtí òun bá sì kúrò níbẹ̀, pé wón o gba òun sí isẹ́ ní ilé isé tiwọn. Nígbàtí ẹnití ó ni isẹ́ gbọ́ ohun tí ìríjú aláìsòótọ́ yì se, ó pè ó sì ní:

***Olúwa rẹ̀ sì yin aláìṣòótọ́ ìríjú náà, nítorí tí ó fi ọgbọ́n ṣe é.***

Ìtumọ̀ pé ó fi ọgbọ́n se é: Ná nì pe ó lo ìmòye ọlọ́gbọ́n tàbí pẹ̀lú ìwádi, pàpá jùlọ ní irú ǹkan báyìí. Kí ó sọnù tàbí kí ó tí sààmìsí bí ẹnití kò lóòótọ́ àti ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́; ẹlẹ́tàn.[11]

Olúwa rẹ̀ rí wípé ìríjú yì ní agbára láti se ohun tí ó le mú èrè wá fún un, tí kì ìse fún ẹnití ó ni isẹ́ bíkòse fún ara rẹ̀—nkan tí kò rí lára ìríjú yí nítorí tirẹ̀. Síbẹ̀síbẹ̀, nígbàtí ó bá di pé kí a tọ́jú ara ẹni, ó ńsọ nípa tí ara rẹ̀ nìkan àti ohun gbogbo tí ó ní se nípa ara rẹ̀ kò ti ẹ̀ ro ti olúwa rẹ̀ rara. Jẹ́kí nsọ fún ọ níbíyìí—alágbàse ni o jẹ́!

Nísisìyí jẹ́ kí nbèrè ìbéèrè kan tí ó le díẹ̀: Krìstíańì alágbàse ni ọ?

Sé ti ara rẹ nìkan ni o mọ̀ ju isẹ́ ti Ọlọ́run lọ? Sé ti ara rẹ nìkan ni ó jẹ ọ́ lógún ju ìtọ́jú ti Ọlọ́run àti nkan Ọlọ́run? Sé o ńfi ohnu ìní Ọlọ́run sòfò?

Wow, Mo mọ̀ pé àwọn ìbéèrè tí ó le ní wọ́n jẹ́. Ìdí sìnìyìí tí mo fi sọ òwe tí ó se pàtàkì yìí gan, nítorí ó wọ ọkàn ẹni lọ àti se àfihàn àwọn ìwà tí kòdára tí a le ma hù níkọ̀kọ̀.

Jésù fi àwọn ìran kan fún wa ó sì se àlàyé ohun tí isẹ́ alágbàse nínú ìwe Jòhánnù 10:11-13.

> *"Èmi ni olùṣọ́-àgùntàn rere: olùṣọ́-àgùntàn rere fi ọkàn rẹ̀ lélẹ̀ nítorí àwọn àgùntàn. Ṣùgbọ́n alágbàṣe, tí kì í ṣe olùṣọ́-àgùntàn, ẹni tí àwọn àgùntàn kì í ṣe tirẹ̀, ó rí ìkookò ń bọ̀, ó sì fi àgùntàn sílẹ̀, ó sì fọ́n wọn ká kiri. Òun sálọ nítorí tí ó jẹ́ alágbàṣe, kò sì náání àwọn àgùntàn.*
>
> —Jòhánnù 10:11-13

Atúmọ̀ Ọba Jákọ́bù Titun ( ẹsẹ.13) sọ ní ònà yìí:

[11] Ìwé Ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ ti èdè Gẹ̀ẹ́sì àtúnse kaàrún ti Amérícám Héritagè.

*Òun sálọ nítorí tí ó jẹ́ alágbàṣe, kò sì náání àwọn àgùntàn.*

Nítorí ìríjú aláìsòótọ́, kò yẹ láti má sètọjú owó olúwa rẹ̀ nítorí tí kò náání ìtọ́jú olúwa rẹ̀; ti ara rẹ nìkan ní ó náání. Níbáyìí, ó sì tún ní agbára láti jáde àti ní owó ara rẹ̀, bẹ́ẹ̀ni, sùgbọ́n kò ní le ní ànfàní láti le mú ÀTI jẹ́ owó olúwa rẹ̀.

Mo gbàgbọ́ pé gbogbo wa ni a ńgbé ní àkókó tí àwọn alágbàse ńlo lààkáyè wọn láti máa se isẹ́ ẹ̀gàn ní Amẹ́ríkà àti ní àgbáye.

Mo mọ̀ pé ó ti lọ sí ilé óunjẹ kan rí tí o sì ti rí tábìlì tó dọ̀tí ati ilẹ̀lẹ̀ wọn tí ó dọ̀tí, àti lẹ́yìn ọ̀rẹyìn, ó rí àwọn òsìsẹ́ kan tí wọn túnse àwáwí. Tàbí ó sáré dé ilé ìta óunjẹ ní kíákíá ní bí ọgbọ̀n ìsẹ́jú kí wọn palẹ̀mọ́ àti lọ ilé, ó wá yà ọ́ lẹ́nu pé o ri tí wọ́n kó àwọn àga sórí tábìlì àwọn òsìsẹ́ sì ti setán kí ago tó kí wọ́n máa lọ. O mọ̀, laíjẹ́ pé o bèrè, ẹnití o ni ilé ìtajà kò sí níbẹ̀. Gbogbo àwọn wọ̀nyìí ni alágbàse. Èrè ọjà na kò kàn wọ́n. Wọn wà níbẹ̀ láti gbà owó isẹ́ ti wọn bá se ni ó titán.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn agbanisísẹ́ ni wọ́n ti sọ fún mi rí pé nkankan ńburú sí ni tí wọ́n bá rí òsìsẹ́ kan tí ó tètè dé ibisẹ́ lásìkò, ti ẹ̀ dáyàtọ̀ láàrin àwọn èrò ni. Àwọn agbanisísẹ́ nkígbe fún àwọn oníkan, kì íse àwọn alákóso. Wón fẹ́ òsìsẹ́ tí yóò sisẹ́ tí yòò tún máa sètójú isẹ́ nà bí isẹ́ ti ara wọn. Wọn sọ fún mi pé òsìsẹ́ tí ó gbé ara rẹ̀ pẹ̀lú irú àwọn ìwà yí ni a ó gbéga àti gbé jáde.

Ọlọ́run kò yàtọ̀. Ó ńwá àwọn ènìyàn tí yóò nání ohun tí Ọlọ́run ná nání àti kórira ohun tí Ọlọ́run na kórira.

Nínú 1samueli 15, Ọlọ́run sọ fún Ọba Sáùlù láti kojú ìjà sí Ámálẹ́kì nítorí ohun tí wọ́n se sí àwọn ọmọ Ísraẹ̀lì ní ojú ọ̀nà wọn sí Èjíbítì. Wọn sọ fún ọba Sáùlù pé kí ó má dá ẹnikẹ́ni sílẹ̀ láàyè. Wọn kò sì gbọdọ̀ mú ẹrankokẹ́ranko kankan padà wá bá wọn, sùgbọ́n nkan tí Sáùlù se nìyìí:

> *Ṣùgbọ́n Saulu àti àwọn ọmọ-ogun rẹ̀ dá Agagi sí àti èyí tí ó dára jùlọ nínú àgùntàn àti màlúù àti ọ̀dọ́-àgùntàn àbọ́pa àti gbogbo nǹkan tó dára. Wọ́n kò sì fẹ́ pa àwọn wọ̀nyí run pátápátá ṣùgbọ́n gbogbo nǹkan tí kò dára tí kò sì níláárí ni wọ́n parun pátápátá.*
>
> —1 Samueli 15:9

Wo nkan tí Ọlọ́run wá sọ ní ẹsẹ 10-11:

*Nígbà náà ni ọ̀rọ̀ OLÚWA tọ Samuẹli wá pé: "Èmi kááànú gidigidi pé mo fi Saulu jẹ ọba, nítorí pé ó ti yípadà kúrò lẹ́yìn mi, kò sì pa ọ̀rọ̀ mi mọ́."*

Nígbàna a rí tí Ọlọ́run bá Sámúẹ́lì sọ̀rọ̀ nípa Sáùlù nínú 1 Samueli 16:1.

*OLÚWA sọ fún Samuẹli pé, "Yóò ha ti pẹ́ tó tí ìwọ yóò máa dárò Saulu, nígbà tí ó jẹ́ pé mo ti kọ̀ ọ́ ní ọba lórí Israẹli? Rọ òróró kún inú ìwo rẹ, kí o sì mú ọ̀nà rẹ pọ̀n, Èmi rán ọ sí Jese ará Bẹtilẹhẹmu. Èmi ti yan ọ̀kan lára àwọn ọmọkùnrin rẹ̀ láti jẹ ọba."*

Gẹ́gẹ́ bí ìrújú alaisòótọ́ tí a lé kúrò láti máa sàkóso ilé isẹ́, bẹ́ẹ̀, nà ni a yọ Sáulù na kúrò. Wá wòó pé kíló selè? A le yọ ìwọ àti èmi na kúrò bákanna.

Kín ní Ọlọ́run ńretí? Ẹníti ó se gbẹkẹ̀lé?

*Nígbà tí Ọlọrun yọ ọ́ lóyè, ó gbé Dafidi dìde fún wọn bí ọba. Ọlọrun jẹ́rìí sí ìwà rẹ̀ nígbà tí ó sọ pé, 'Mo rí i pé Dafidi ọmọ Jese jẹ́ ẹni tí ọkàn mi ń fẹ́, <u>ẹni tí yóo ṣe ohun gbogbo bí mo ti fẹ́</u>.*

— Awon Aposteli 13:22

Tí a bá le yọ wá kúrò, a sì tún le gbàwá padà. O le sọ pé, Ó da, Garry báwo ní mo ti se le seé? Òwe yií ni yóò dáhùn ìbéèrè rẹ.

*"Ẹni tí ó bá ṣe olóòtítọ́ nínú ohun kínkínní, ó ṣe olóòtítọ́ ní púpọ̀ pẹ̀lú: ẹni tí ó bá sì ṣe aláìṣòótọ́ ní ohun kínkínní, ó ṣe aláìṣòótọ́ ní ohun púpọ̀ pẹ̀lú. Ǹjẹ́ bí ẹ̀yin kò bá ti jẹ́ olóòtítọ́ nínú ọrọ̀ ayé "Olúwa rẹ̀ sì yin aláìṣòótọ́ ìríjú náà, nítorí tí ó fi ọgbọ́n ṣe é: àwọn ọmọ ayé yìí sá à gbọ́n ní Ìran wọn ju àwọn ọmọ ìmọ́lẹ̀ lọ. Ǹjẹ́ bí ẹ̀yin kò bá ti jẹ́ olóòtítọ́ nínú ọrọ̀ ayé yìí, ta ni yóò fi ọ̀rọ̀*

*tòótọ́ fún yín? Bí ẹ̀yin kò bá sì ti jẹ́ olóòtítọ́ nínú ohun tí í ṣe ti ẹlòmíràn, ta ni yóò fún yín ní ohun tí í ṣe ti ẹ̀yin tìkára yín?*

*"Kò sì í ẹnìkan tí ó lè sin ọ̀gá méjì. Òun yóò yà kórìíra ọ̀kan tí yóò fẹ́ràn èkejì, tàbí kí ó fi ara mọ́ ọ̀kan kí ó sì yan èkejì ní ìpọ̀sí. Ẹ̀yin kò lè sin Ọlọ́run àti owó papọ̀."*

—Luku 16:10-13

Jẹ́kín sọ kí ó ye ọ: o gbọdọ̀ yege nínú ìdánwò síse olóòtítọ́. Tí wọ́n bá le gbà ọ gbó nínú kínkínní, wọn ó gbà ọ́ gbọ́ nínú púpọ̀. Ìdánwò na máa ńwáyé nínú tí ara sí tí ẹ̀mí. O gbọdọ̀ jẹ́ ẹnití a le gbàgbọ nínú kí á kó ohun ọrọ̀ ti ayé lé lọ́wọ́ kí Ọlọ́run tó wá gbà ọ gbọ́ láti kó ọrọ̀ Rẹ̀ lé ọ lọ́wọ́. Tí o kò bá jẹ́ olóòtítọ́ pèlú ohun ìní ẹlòmíràn, tani yóò wá fi ohun ìní tirẹ̀ gan fún ọ? Ó dájú kí isẹ́ Ọlọ́run.

Ó dára. Òwe kan nìyí tí ó bá ayé tiwa gan mu.

**Àjẹkù ni ọ̀pọ̀ Krìstíánì máa fifún Ọlọ́run.**

Ọ̀pọ̀ Krìstíánì ni wọ́n máa nwo ètò ìsúná wọn àti se ìpinnu pé, "Nkan tí mo le fi sílẹ̀ nìyìí," Síbẹ̀ kò sí wàhálà kankan fún wọn láti lọ ra ọkọ̀ ojúomi titun ní ọjọ nà.

Níbáyìí, Kì íse pé mo fẹ́ kí ẹnikẹ́ni má ní ìdálẹ́bi ní ọkàn rẹ, Ọlọ́run pẹ̀lú kò bínú sí pé o ní ọkọ̀ ojú omi tódára. Mo kàn nbi ọ́ lérè ni pé: Sé owó ti ara rẹ nìkan ni o fẹ́ kó dání ni tàbí tìrẹ àti ti Ọlọ́run?

Tí o bá lo gọ́ọ́gù ohun tí ìdáméjì Krìstíánì fifún Ọlọ́run, O le yà ọ́ lẹ́nu. Mo rí ìsirò kan tí o kọ pé ìdáméjì Krìstíánì fún Ọlọ́run ní Pọ́ùn mẹ́tàlá ó lé ní díẹ̀ ní òsẹ̀ kan sí ìjọ.[12]

Mo wá wo ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìsirò tí ó níse pẹ̀lú ìfifúnni, gbogbo rẹ̀ ló burújáì. Gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ, Ọ̀pọ̀ Krìstíánì ni ò nfún Ọlọ́run ní àwọn àjẹkù. Lẹ̀ẹ̀kansíi, jọ̀wọ́ jẹ́ kí ó yé ọ èmi kò gbìyànjú láti dá ọ lẹ́bi tàbí kí o má ní ìdálẹ́bi ní ọkàn rẹ. Mo kàn ńsọ kókó ọ̀rọ̀ ni-mo sìrò pé ọ̀rò Ọlọ́run gbé ọ̀rọ̀ mi dúró-pé Ọlọ́run kò wá àwọn alágbàse; àwọn oníkan na ni ó ńwá.

[12] https://www.pastorrickypowell.com/life_matters_with_pastor_/2009/10/startling-statistics

Ẹlẹkejì, Ọlọ́run kò wá àwọn ènìyàn tí a o maarọ̀ wọn kí wọ́n tó fifúnni kúrò ní ẹ̀bi ọkàn wọn. Ọlọ́run ńfẹ́ onínú dídùn ọlọ́rẹ, gégé bí ìwé 2 Kọ́ríntì 9:7 ti sọ.

Sáùlù ni a yọ kúrò nítorí kò se ohun tí Ọlọ́run nípé kí o se, Sùgbọ́n a yan Dáfídì nítorí yóò gbọ́ràn àti se ohun tí Ọlọ́run bá fẹ́ kí ó se.

Torínà, jẹ́ kí ntún dàba ìrísí titun kan. Tí o bá jẹ́ pé awá yí ayé padà doríkodò tí a pinnu láti máa fún Ọlọrun ní àkókò tí àwa wa bẹ̀rẹ̀ sí ní gbé ayé wa lórí àjẹkù na? Mo le fi dá ọ lójú pé àjẹkù rẹ̀ yí kò nípẹ́ tí yóò fi le ọ bá tí wà sì ma gbé ayé tó ní ìbùkún.

Ó sisẹ́ fún R.G. LeTourneau. Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ pẹ̀lú ìtẹ́ríba àti ẹ̀kọ́ onípele keje, òun ni ó kọ ara rẹ̀ àti fúnra rẹ̀ kọ́ ilé isẹ́ àwọn ẹ̀rọ ńlá. Irinsẹ́ rẹ̀ kan tí ó se ní ó rán WWII láti gbégbá orókè àti kọ́ òpòpọnà amáyédẹrun tí ìgbàlódé ní Amẹrikà. Ní opin ọjọ ayé rẹ̀, ó ti ni tó ọ̀ọ́dúnrún àwọn ìwé tí ó lé mú bẹ̀rẹ̀ ohunkóhun.[13]

Àsírí rẹ̀ ó nfumn Ọlọrun nim ìdá àdọ́ọ́run nínú ohun gbogbo tí ó bá ti rí.[14]

Níbáyìí, mi ò sọ fún ọ pé kí o se ohun kan na. Èyí ni àdéhùn tí òun àti Ọlọrun jọ sọ nígbàtí ó wà ní ọmọ ọgbọ̀n ọdún tí ó sì wà nínú gbèsè. Ó fi Ọlọ́run se alábásisẹ́pọ̀ nínú oko òwò rẹ̀ (bí ó ti se pè é) ó sì parí bẹ́ẹ̀.

Nígbàtí Ọlọ́run pè mí lamti lọ bẹ̀rẹ̀ ìjọ láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, nígbànà mo ti ní ilé isẹ́ tí mò ńdarí, Forward Financial Group. Tí ó sì ti gbílẹ̀ gan ilé isẹ́ yí ní àkókò na nínú bí ẹgbẹ̀rún máàrún irú rẹ̀ tí ó wà káàkiri ní àgbáyé pẹ̀lú àwọn alágbàtà pẹ̀lú. Nígbàtí Ọlọ́run pè mí sí isẹ́ ìránsẹ́, mo bèrè lọ́wọ́ rẹ̀ pé, "kín ni yóò wá sẹlè sí Forward Financial Group? Sé kín ti ilé isẹ́ nà pa ni kín sì kọjú mọ́ isẹ́ pásítò ìjọ mi?"

Olúwa sì dá mi lóhùn pé*, Rárá, máa sé lọ nítorití ó ńran àwọn ènìyàn lọ́wọ́"* Bẹ na ní mo sì se.

Mo gbàpé nígbàmíràn o máa ńle láti le se méjèjì papò, sùgbọ́n ó ti ran ẹgbẹ̀rún ènìyàn lọ́wọ́ ní ọ̀pọ̀ ọdún sẹ́yìn. Bí mo ti ńse pásítọ̀ nínu ìjọ

[13] http://centerforfaithandwork.com/article/who-was-rg-letourneau

[14] http://centerforfaithandwork.com/article/why-rg-letourneau-gave-90-percent

wa, Mo nwo pé ilé isẹ́ mi má ní ìfàsẹ́yìn díẹ̀ nínú isẹ́ tí wọ́n ńse nítorí tí èmi kò ní rí àyè se bí titẹ̀lẹ̀ mọ́. Sùgbọ́n bim èmi àti Drenda ti fi gbogbo àyè wa sílẹ̀ láti rípé a se àseyọrí nínú isẹ́ tí Ọlọ́run gbé lé wa lọ́wọ́, ìdákẹ́jì ni mo ńrí o. Kódà bíótijẹ́pé ìgbà díẹ̀ ni mo ńlò pẹ̀lú ilé isẹ́ mi,síbẹ̀ ó sì tún lọ dáadáa.

Láàrin bí ọgọ́rún àwọn ọ́fisì ní àgbáyé asì tún wà láàrin àwọn máàrún sí mẹ́wa tí gbogbo ayé dámò. Síbẹ̀ mo ní láti rẹ́rin, torí mo mọ̀ pé àsìkò dìẹ ni mo ní fún un torípé mo nsisẹ́ Pásítò ní gbogbo ìgbà. Ọlọ́run fi ọlá fún mi pẹ̀lú ojúrere àti ọgbọ́n tí ó fi jẹ́ pé gbogbo àwọn tí ó wà ní ayé tí wọ́n ńfi gbogbo ọjọ́ ayé wọn wá owó kiri ní láti má yà wọ́n lẹnu pé báwo ni mo ti se ńse.

Mo le rántí tí mo jókòó ní ibi ìpàdé àpérò kan tí arakùnrin tí ó jókóò ní ẹ̀gbẹ́ mi ńbèrè lọ́wọ mi pé ìmọ̀ nípa ọjàtítà mélo ni mo se. Mo kàn rẹ́rin mo sì dáhùn pé “kòsí kankan.” Ó wá bèrè, Ó dá báwo ni o se wá ńse oko-òwò tó pọ̀ tó báyìí? Mo wá sọ fún pé a kàn ńsisẹ́ òrọ̀ ẹnu ni Ọlọ́run sì bùkún wa. Ó kàn mi orí pé bí kò ti se le sọ nkan tó nsẹlẹ̀.

Ní àsìkò kan, Ààrẹ ọ̀kan nínú àwọn ẹgbẹ́ alágbàtà wá pé ó sì fẹ́ láti mọ̀ bóyá mo le bá àwọn tí ó wà sí ìpàdé sòrò lórí bí mo ti se ńse àseyọrí púpọ̀ tó bẹ̀. Mo ní inú mi yóò dùn láti se bẹ. Ó wá bẹ̀rẹ̀ sí níbèèrè àwọn ìbéèrè nípa bí a ti se ńse isẹ́ wa àti bí a sì ti ń se oko-òwò wa pẹ̀lú. Bẹ́ẹ̀ni, mo ni láti sọ fún bí a ti fi ìgbẹ́kẹ̀lé wa sínú Ọlọ́run àti bí ó ti se bùkún wa pẹ̀lú ojúrere rẹ̀. Lẹ́yìn tí mo ti sọ fún pé àsìkò díẹ̀ ni àrin ọ̀sẹ̀ ni mo ní láti fi se isẹ́ nà nítori pásítò ìjọ kan ni mo jẹ́, ó wá sọ pé “Ó da, mo lérò pé ẹnití ó kọ́ ẹ̀kọ́ nípa ìlànà ète bí o ti se ńtajà ní àti pé wa pín pẹ̀lú wa bí ó ti se nsisẹ́. Mi ò rò bẹ nkan tí mo ní lokàn, sùgbọ́n mo mọ rírì bí o ti ní lọ́kàn láti pín ìrírí rẹ pẹ̀lú wa. Háà, ó dára, aìmọ̀ kàn wọn ni. Mi ò bá ti ran ọ̀pọ̀ àwon ènìyàn lọ́wọ́ níbiyi.

**ỌLỌ́RUN TI RÍI. NÍNÚ GBOGBO ISẸ́, À ŃKỌ́ Ọ LẸ́KỌ FÚN ÌPELE TÓ KÀN, TORÍBẸ̀ MÁ KẸ́GÀN ỌJỌ́ ÌBẸRẸ KÉKERÉ LÁÍLÁÍ.**

Mo ti sọ ọ́ láti ìbẹ̀rẹ̀ dókè ìwé yìí pé tí o bá tí ńtọjú isẹ́ ti Ọlọ́run, yóò máa tojú ise tìrẹ naa!

Toríbẹ̀, jẹ́ kín bi ọ́ léèrè ìbéèrè tí a bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú rẹ, Owó tani ó ńse?”

Sé ó kúkú má tọ́jú owó tí ó jẹ́ tìrẹ, bí ti ìríjú aláisòótọ̀ tàbí sé o fẹ́ má

sètọ́jú owó ti Ọlọ́run bákanna? Nígbàti o bá nsètọ́jú owó ti Ọlọ́run, àwọn irúgbìn oko-òwò rẹ yóò ma ní agbára nípa ọgbọ́n ti Ọlọ́run àti ore ọ̀fẹ́, Tí ó mú ìkórè óunjẹ ti ara ẹni tí yóò sì mú pípọ̀si wá pẹ̀lú.

Mo mọ̀ ó sì dámilójú pé kò kan Ọlọ́run bí o bá ní millíọnù míliọ́nù lọ́wọ́ níwọ̀n gbàtí Ó ti ní ọkàn rẹ!

Rántí, pé o bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú isẹ́ kékeré níbití ẹnikẹ́ni kò mọ orúkọ rẹ. Kódà o le máaronú pé kò sí ẹnití ó fẹ mọ nkan tí ò nse nípa ti isẹ́ tí ò ńse, Ọlọ́run tị ríi. Nínú gbogbo isẹ́, à ńkọ́ ọ lẹ́kọ fún ìpele tí ó ó kàn, toríbẹ̀, má kẹ́gàn ọjọ́ ìbẹ̀rẹ̀ kékeré. Má se bí ìgbàtí o jẹ́ pé ìwọ ni ó ni àti kí o sì fi gbogbo ipá rẹ seé. Mo fi dá ọ lójú wípé wa má tàn bi ìràwọ̀ òru níkẹyìn ni àti fi ara rẹ sí ipò ìgbéga àti ojúrere.

ORÍ KAÀRÚN

# O NÍLÒ ALÁBÁSEPỌ̀!

Bí o ti se mọ̀ pé, mo ti wa lẹ́nu oko-òwò ètò ìsúná fẹ́ẹ̀ tó bí ogbójì ọdún báyìí. Nígbogbo ọdún nà, ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ti máa ńbimí léèrè pé báwo ni awọǹ ti se le bẹ̀re òwò na àti pé kí ni yóò mú kí isẹ́ nà le má dàgbà.

Lóòtọ́, ọ̀pọ̀lọpò ní nkan tí ó yẹ kí àwọn ènìyàn mọ̀, sùgbọ́n ohun tí ó se pàtàkì jùlọ tí mo le sọ fún wọn ni wípé wọ́n o nílò *alábásepọ̀.*

Báyìí, gẹ́gẹ́ bí pásítọ̀ fún ọ̀pọ̀ ọdún, mo ti rí tí ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn mi tí wọ́n lérò pé yóò dára láti lọ bá ọ̀rẹ́ nínú ìjọ wọn sòwò, tí gbogbo rẹ̀ sì bú gbàmù. Àwọn ọ̀rẹ́ se ara wọn, ní ọ̀pọ̀ ìgbad wọ́n kò ní bá ara wọn sọ̀rọ̀ mọ́, tí ìbásepọ̀ wọn yóò sì túká. Nimtorí mo ti rí èyí ní ọ̀pọ̀ ìgbà, torí rẹ̀ mi òní sọ fún ọ pe kí o lọ dòwòpọ̀ pẹ̀lú ọ̀rẹ̀ àyàfi tí ẹ bá ti jọ ní àdéhùn tí ẹ sì ti jọ fọwọ́ bòwé àkọsílè.

Síbẹ̀síbẹ̀, alábásepọ̀ kan wà tí mo má ńsọ pé kí o básepapọ̀, òun ná ni Ọlọ́run.

Nínú ìpín tí a kà sáajú, a sọ̀rọ̀ nípa obìnrin tí ó gba wòlíì Èlíjàh tí ó sì fun ní óunjẹ rẹ̀ tó kẹ́yìn. A rí bí o ti gbé ìgbésè ìgbàgbọ tí sì ń fún wòlíì ní óunjẹ ní ojojúmọ́, isẹ́ Ọlọ́run àti fún ìdílé obìnrin na. O sisẹ́papọ̀ pẹ̀lú rẹ̀ nínú isẹ́ tó ńse, àti ní síse bẹ, ìfòróróyàn àti ìpèsè tí ó wà lórí isẹ́ àkànse rẹ wá di tìrẹ. Wọ́n di alábásepọ̀.

Ní ìbẹ̀rẹ̀ dọ́pin ìwé yìí, ni a ti ńsọ̀rọ̀ nípa lílawọ́ sí Ọlọ́run àti fúnfúrúgbìn sí àwọn isẹ́ Rẹ̀. Mo sì tún ti sọ fún yín lílawọ́ àti jẹ onínúrere láti sí ọkàn àwọn ènìyàn sí ọ àti sí Ọlọ́run bákanna.

Nínú ìpín yìí, mo fẹ pín pèlú rẹ ìlànà òfin míràn tí o tún lágbára tí Ìjọba Ọlọ́run tí yóò mú ìsúná rẹ lọ sí ìpele titun—ìlànà òfin ti alábásepọ̀.

*Ó sì ṣe, nígbà tí ìjọ ènìyàn súnmọ́ ọn láti gbọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, tí ó sì dúró létí adágún Genesareti. Ó rí ọkọ̀ méjì ti o wá létí adágún: èyí tí àwọn apẹja ti sọ̀kalẹ̀ kúrò nínú wọn, nítorí tí wọ́n ń fọ àwọ̀n wọn. Ó sì wọ ọ̀kan nínú àwọn ọkọ̀ náà, tí í ṣe ti Simoni, ó sì bẹ̀ ẹ́ kí ó tì í sí ẹ̀yìn díẹ̀ kúrò ní ilẹ̀. Ó sì jókòó, ó sì ń kọ́ ìjọ ènìyàn láti inú ọkọ̀ náà.*

*Bí ó sì ti dákẹ́ ọ̀rọ̀ sísọ, ó wí fún Simoni pé, "Tì í sí ibú, kí o sì ju àwọ̀n yín sí ìsàlẹ̀ fún àkópọ̀."*

*Simoni sì dáhùn ó sì wí fún un pé, "Olùkọ́ni, gbogbo òru ni àwa fi ṣiṣẹ́, àwa kò sì mú nǹkan kan: ṣùgbọ́n nítorí ọ̀rọ̀ rẹ èmi ó ju àwọ̀n náà sí ìsàlẹ̀."*

*Nígbà tí wọ́n sì ti ṣe èyí, wọ́n kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja: àwọ̀n wọn sì ya. Wọ́n sì pe àwọn ẹgbẹ́ wọn, tí ó wà nínú ọkọ̀ kejì, kí wọn kí ó wá ràn wọ́n lọ́wọ́. Wọ́n sì wá, wọ́n kó ẹja ọkọ̀ méjèèjì sì kún, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í rì.*

—Lúkù 5:1-7

Mo mọ̀ pé mo ti sọ ìtàn yí sáájú nígbàtí a ńsọ̀rọ̀ nípa ọkọ̀ ojú-omi àti isẹ́ oko-òwò ẹja síse tí ìjọba ýipadà (tàbí sàkání) nígbàtí Pétérù (Símónì) yá Jésù ní ọkọ̀ ojú-omi wọn láti fi wàásù. Mo tún ti sọ nípa ẹja aláràgbàyídá tí wọn rí kó tí o sẹlẹ̀ tí ọkọ̀ ojú-omi wọn méjéjì sì fẹ́ rì. Rántí, Pétérù sọ pé òun ti fi gbogbo òru na wá ẹja tí òun kò sì rí ẹja kankan pa. Níbáyìí, láàrin bí wákàtí díẹ̀, ó sì rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja tí òun fúnrarẹ̀ kò le dáa fà. Kínni ìyàtọ̀ tó wà níbẹ̀? Ìjọba, dájúdájú, sùgbọ́n bákanna *alábásepọ̀*. Jẹ́ kín sàlàyé.

*Ó rí ọkọ̀ méjì ti o wá létí adágún: èyí tí àwọn apẹja ti sọ̀kalẹ̀ kúrò nínú wọn, nítorí tí wọ́n ń fọ àwọ̀n wọn. Ó sì wọ ọ̀kan nínú àwọn ọkọ̀ náà, tí í ṣe ti Simoni, ó sì bẹ̀ ẹ́ kí ó tì í sí ẹ̀yìn díẹ̀ kúrò ní ilẹ̀.*

Jẹ́ kín sọ́ kí ó yé wa dáda ní ọkàn wa. Níbo ni wọ́n wà, àti pé kín ni wọ́n ńse lọ́wọ́ nígbàtí Jésù wá bá wọn? Kì íse pé wọn ńpa ẹja ni; wọn wà ní etí adágún wọ́n ńfọ àwọ̀n wọn lẹ́yìn ìgbàtí wọ́n ti fi gbogbo òru sisẹ́ tí

wọn kò sì rí ẹja kankan pa.

Jésù, sàkíyèsí pé ọkọ̀ ojú-omi na wà nílẹ̀, ó sì bi Pétérù léèrè pé tí o bá le tì sẹ́yìn díè kúrò ní ilẹ̀ kí Òun ba le lò ó láti wàasù fún ọ̀pọ̀ ènìyàn. Toríbẹ, níbo ni Jákọ́bù àti Jòhánù wa, àwọn alábasepọ̀, nígbàtí ó mú Jésù jádè kúrò nínú ọkọ̀ ojú-omi? Ó da, Wọ́n sì wà ni etí adágún pẹ̀lú àwọn ọkọ̀ ojú-omi míràn àti àwọ̀n wọn.

Lẹ́yìn ìgbàtí ó wàásù tán, Jésù sọ fún Pétérù ju àwọ̀n rẹ sínú ìbú láti kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja. Sebí ìwọ na mọ ìtàn na. Ó sì bẹ̀rẹ̀ sí ní kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja tí àwọ̀n rẹ̀ sì fẹ́ẹ̀ ya. Toríbé ó pe à wọn alábásepọ̀ rẹ̀ pé kí wọ́n wà láti ran òun lọ́wọ́ fa ẹja na. Bíbélì sì sọ pé àwọn ọkọ̀ méjéjì na sì fẹ́ rìi, torí wọ́n kún fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja.

> *Nígbà tí wọ́n sì ti ṣe èyí, wọ́n kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja: àwọ̀n wọn sì ya. Wọ́n sì pe àwọn ẹgbẹ́ wọn, tí ó wà nínú ọkọ̀ kejì, kí wọn kí ó wá ràn wọ́n lọ́wọ́. Wọ́n sì wá, wọ́n kó ẹja ọkọ̀ méjèèjì sì kún, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í rì.*

Báyìí, ìbéèrè ńlá kan nìyìí oní míllịọnù dọ́llàr: Ìgbàgbọ́ mélo ni Jákóbù àti Jóhánnù lò tí ó mú kí ọkọ̀ ojú-omi wọn kún fún ẹja tí ó sì tún fẹ́ rìi.

Ronú nípa rẹ̀—wọ́n sì tún wà létí adágún pẹ̀lú àwòn wọn. Pétérù ni ó gbà láti gbé Jésù jáde lọ. Òun nà sì ni ẹnití ó sọ pé, "*Sùgbọ́n nítorí ọ̀rọ̀ rẹ èmi ó ju àwọ̀n náà sí ìsàlẹ̀.*" Torínà ìdáhùn tí ó tọ́ nipé kòsí! Jákọ́bù àti Jóhánnù wọn kò kórè ẹ̀kún ẹja tí ó wà nínú ọkọ̀ ojú-omi nítorí ìgbàgbọ́ *wọn*; Nítorí ìgbàgbọ́ Pétérù ni. Pétérù kàn pè àwọn alábásepọ̀ rẹ̀ tí wọ́n wà létí adágún láti wá ràn án lọ́wọ́ àti kó ẹja na. Sí ìyàlẹ́nu, ọkọ̀ ojú-omi wọn kún ní déédé bí Pétérù ti ní, láti kún àkúnwọ́sílẹ̀.

> *Simoni sì dáhùn ó sì wí fún un pé, "Olùkọ́ni, gbogbo òru ni àwa fi ṣiṣẹ́, àwa kò sì mú nǹkan kan: ṣùgbọ́n nítorí ọ̀rọ̀ rẹ èmi ó ju àwọ̀n náà sí ìsàlẹ̀."*

Tí o bá jẹ́ ìgbàgbọ́ tí Pétérù ní ó mú kí ẹja wá àti mú kí ó kún inú ọkọ̀ ojú-omi, Kín wá lódé tí ọkọ̀ ojú-omi ti Jákọ́bù ati ti Jòhánnù na fi wá kún

fún ẹja bí ti ọkọ̀ ojụ-omi ti Pétérù náà se kún?

Ẹsẹ Bibéli yì ní ó dáhùn ìbéèrè—ó sọ wípé *alábasepọ̀* ni wọ́n.

Ìtumọ̀ alábasepọ̀ nínú atúmọ̀ èdè Collins English Dictionary ni:

> **Ẹnití ó ńpín tàbí jẹ́ ẹnití ó ní nkan se papọ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn nínúÀwọn isé kan tàbí ìgbìyànjú; tí ó pín ewu àti èrè rẹ̀ nígbàgbogbo.**

Alábasepọ̀ jé nkankan tí ó lẹ́tọ lábẹ́ òfin láti pín nínú àwọn ewu, ìdíyelé, àti èrè orí okò-òwò. Toribẹ̀, nígbàtí Pétérù fún Jésù ní ọkọ̀ ojú-omi láti lò, ó kúkú ńyá Jésù ni *oko-òwò rẹ* ni tí a bá wòó lábẹ́ òfin; kì íse ọkọ̀ ojú-omi nìkan. Tí a bá fi ìlànad ti isẹ́ wòó, Jákọ́bù àti Jòhánnù na ní lára ọkọ̀ ojú-omi tí Pétérù jẹ́ kí Jésù lò, nítorí alábasepọ̀ ni wọ́n jẹ́, àwọn ọkọ̀ ojú-omi méjéjì ni ó sì kún bákanna.

Jákọ́bù àti Jòhánnù na ka *déédé iye ìkórè kanna* bí Pétérù ti se bíotilẹ̀jẹ́pé wọ́n ò tílẹ̀ lo ìgbàgbọ wọn ní ipò na rárá. Mo sọ fún ọ pé inú wọn yóò dùn pé Pétérù àti àwọ́n jọ jẹ́ alábasepọ̀ ní ọjọ́ nà. Kín lo rò? Mo rò bẹ́ ni. Jẹ́ kín tún fún ọ ní díẹ̀ si lára àpẹẹrẹ ti ara mí níti ìlànad òfin yìí.

Èmi àti Drenda ní ọgọ́ta saare ilẹ̀ tí ó dára tí ó ní àwọn igi, àkùrọ̀ àti koriko. Ó jẹ́ ibití ó dára gan láti sọdẹ àgbọ̀nrín. Ọ̀pọ̀ ohun ọgbìn ni wọ́n gbìn yí àyíká ilé wa, tí àwọn igi, àkùrọ̀ yí jẹ bí ònfà fún àwọn àgbònrín yìí.

Mo wá kọ́ ọfisì mi si ẹ̀gbẹ́ gárejì wa, tí ó sì ní ibi ìkówe sí tí a fi igi se àti kọ ibi ìdáná gáásì. Ó jẹ́ ibití ó dákẹ́ ni, o dàbí ọfisi tí ó wà ní ihò ilẹ̀, tí mó sì nífẹ láti má sisẹ́ nibẹ̀. Ohunkan tí ó dára tí kò sí níbẹ̀ na ni akọ àgbònrín ńla lórí tábìlì mi. Kín sọ òtítọ́ fún yin, mo o tilẹ̀ fẹ́ràn láti má yìnbọn sí akọ àgbọ̀nrín ńla, bí mo ti jẹ́ ọdẹ apẹran. Àtí pe bẹ̀ mi ò tí bá wọn yìnbọn sí àgbọ̀nrín tí ó ti tóbi tó máa gùn lo.

A sì tí ńgbé lórí ilẹ̀ wa náà tó bí ọdún máàrún nígbàtí Drenda nípé kí nyìnbọn mó àgbònrín ńla kan láti inú ọfisi mi. títí ó fi di ìgbàna, mí ò ti rí ẹran ńlá tí ó tóbi bẹ́ ẹ̀ rí lórí ilẹ̀ wa. Mo ti ma jáde lọ ní àsìkò láti pa ẹran àgbọ̀nrìn mo sì ti yìnbọn mọ́ ọ̀pọ̀ ní à moye ìgbà bi àwọn mẹjọ, sùgbọ́n kò sí ohun tí ó fẹ̀ mu mi ro àsìkò atigùn wọn.

Sùgbón ní ọdún tí à ńsọ yìí, bí mo ti ńronú nípa rẹ̀, ni mo gbà pẹ̀lú

Drenda. Mo sọ fún Drenda pé mà fẹ́ láti lọ wá àgbọ̀nrín kan pa. Lẹ̀ẹ̀kansi, Mi ò sì ti rí akọ àgbònrín ńlá ní agbo àwọn igi. Fèrèsé ilé ìdáná wa kọjú sí orí pápá tí igi wà, síbẹ̀ mi ò tí rí ẹyọ kan.

Toribẹ, èmì àti Drenda wá fúnrúgbìn fún àgbọ̀nrín ńlá. Mo kọ sórí sọ̀wédowó tí mo fi fúnrúgbìn mi sílẹ̀ pé mo ńfúnrúgbìn fún ìwọ̀n mẹwa tabi ti o tun tobi jube lo. A si gbadura lori eso wa, mo si fi sori tabili mi firanse. Apo iwe na si wa nibe fun bi ojo meta, mi o kan le fi ranse ni. Mo mop e mi o ni igbagbo fun àmi mẹwa. Mo ni ìgbàgbọ́ fún mẹ́jọ, mẹ́fà, tàbí mẹrin láti ìgbàyí wá, sùgbọ́n ó ńdá ọkàn mí láàmú pẹ̀lú ìdánílójú àti rí àgbọ̀nrín tí ó tóbí pẹ̀lú ìgbàgbọ̀ tí ó sọ pé “Mo mọ̀ pé Mo mò pé ma pa èyi tí o tóbi tàbi gbé ìwọn mẹwa tí mo bá ti jáde lọ.”

Mo ti ní ìrírí tó pẹ̀lú Ìjọba tí ó fi jẹ́ kín mọ̀ pé mi ò sí nínú ìgbàgbọ́. Toríbẹ Mo fa sọ̀wedowó nà ya mo wa kọ òmíràn tí ó sọ pé àmì mẹrin tàbí tóbi jùbẹlọ mo wa kọọ́ ránsẹ́.

Ní alẹ́ sáajú kín tó jáde lọ, mo sọ fún Drenda ohun tí mo se. “ Mi ò ní ìgbàgbọ́ fún àgbọ̀nrín tí ó tóbi tó bẹ̀ẹ̀,” Mo sọ fún. Ó wá wò mi óní, “O ní ìgbàgbọ́ fún àgborín, èmi ò sì ní ìgbàgbọ́ fún akọ àgbọ̀nrín ńlá. Ọlọ́run sì le se ju ohun tí ò bèrè tàbí tí o lérò lọ!”

Ní òwúrọ̀ ọjọ́ kejì ilẹ̀ mọ́ bí ó ti sé ńmọ́ àwọn ẹyẹ ńkọrin lórí igi bí òórùn ewé tó tara igi bọ̀ o mú mi rántí gbogbo àwọn àgbònrín tí mo ti sọdẹ rẹ̀. Kò sí tí pẹ tí mo jókòó, bóyá bí ogún ìsẹ́jú, tí mo gbọ́ tí ẹran kan ńrúwé bọ̀ láàrin àwọn igi. Àgbọ̀nrín yìí ńbọ̀ wá sí ọ̀nà ọ̀dọ̀ ibi igi mi, mo sì ti setán láti yìnbọn fún.

Bí ẹran yi tí nsúnmọ mi, mo rí pe déede amì mẹrin tí mo sọ gan ni, bí wọ́n ti dá a tó ní jíjẹ. Ó sì jáde sí gbangba ní bi yáàdìì mẹẹ́dọ́gbọ̀n sí ọ̀dọ̀ mi, mo sì ta ọfà na si. Bó se dúnmí tó, mó rí ọfà na tí ó bá a tí o sì tún padà, mo sì mò pé mo ní láti tọ ipa rẹ̀ lọ.

Ẹran na sáré lọ láàrin igi ó sì fò sínú oko àgbàdo tí ó pàlà sí àwọn igi mi o sì ri mọ. Mo sì ńgbọ́ bí ó ti ńsáre lọ láàrin àgbàdo mo sì mò pé bí ó ti ńsáre lọ yìí le mú kin tọpa rẹ̀ lọ sí ibi tí ó jìnnà. Mo wá dúró fún bí ogún ìsẹ́jú ní ẹ̀bá igi kín tó wá pinnu àti wá ọfà na lọ. Mo mọ̀ pé ọfà na bàá, mo sì rí ojú –àpá ẹ̀jẹ̀.

Bí mo ti ńtẹ̀le ojú-àpá ẹ̀jẹ̀ na, ni mo ńgba ara mi níyànjú, bí mo ti rí àpá-ẹ̀jẹ̀ dada. Sùgbọ́n lẹ́yìn bí ìbùsọ̀ ọgọ́rún, àpá-ẹ̀jẹ̀ na ti gbẹ. Mo wá

ńwò yíká àti wò ó sùgbọ́n mi ò rí ojú àpá ẹ̀jẹ̀ mọ. Lẹyìn bí wákàtí méjì tí mo ti ńwá, ni mo tó mò pé àgbọ̀nrín na ti lọ. Ó dùnmí gan. Àkọ́kọ́, mi ò fẹ́láti pa àgbọ̀nrín lára kó wa sálọ kín má ri, èkejì, o dùnmí pẹ̀lú ìbọn mi tí mo yìn.

Bí mo ti dúró síbẹ̀ nínú oko àgbàdo, mo wá rìn padàbọ̀ sí ònà ilé nígbàtí èrò kán wá sí mi lọ́kàn. *Mo sì mọ̀ pé ó tún séése fún mi, mo le rí àgbọ̀nrín na bí mo ti se ńpadà lọ sílé nínú oko àgbàdò yìí tàbí ní ẹ̀bá àkùrọ̀.*

Mo tún ìbọn mi kì, aìbamọ̀. Bí mo sì ti ńrọra lọ lọ́nà ni, lójijì, mo rí tí àgbọ̀nrín kan fò jáde kọjá níwájú mi. Mi ò tílẹ̀ mọ ibití mo wà, àgbọ̀nrín na dúró ó wo ẹ̀yìn. Níwọ̀n igbàtí mo ti wo irú asọ tí mo wọ̀, kamofilagi, àgbọ̀nrín ti mo ńrí yí́ abo àgbọ̀nrín ńlá, ó dàbípékò ní sèlẹ̀, sùgbọ́n láàrin ìsẹ́jú ààyá, sùgbọ́n mo rí àwọn àgbọ̀n, lóòtọ́ mi ò le sọ bí wọ́n titóbi tó tàbí bí àmì tí wọn.

Mo rí pé láàrin ìsẹ́jú kan ni mo pinnu ní ọkàn mi nípa àgbọ̀nrín nà. Ó kọjá jú ibití mo ti le yìnbọn lọ bí́ ọ̀pá márùnléládọ́ta ó sì dúró gbọọrọ sí m. Mo tètè wo ibití ó wà lókè ẹ̀yìn rẹ̀ mo sì yin ọfà mi si.

Lójúkanna ní àgbọ̀nrín ńlá yìí subúlulẹ̀ bí ọfà ti bàá. Kódà àyà mí sì ńjá bákanna. Sé ó ti sẹlẹ̀ bẹ yẹn ná ni?

Bí mo ti lọ si ibití ó subúsí, ohun àkọ́kọ́ tí mo sọ nipé, "Ìgbàgbọ́ Drenda! Àgbọ̀nrín ńla nìyí! Mo ka ó wá jẹ́ mẹrìndínlọ́gbọ̀n àmìì, ó tún ku àwọn agbọ́n bẹ ni bẹ kọ́ bakanna. Mi ò ti rí àgbọ̀nrín tí ó tóbi tó báyi rí! Tí mo bá sọ pé o jọ mi lójú kò ní sọ bó ti rí gan.

Bí ìwọ na ti ri báyìí, àgbọ̀nrín ńlá ti wà lórí tábíli ọfisi mi nísisidyí.

Sùgbọ́n mo fẹ́ sọ̀rọ̀ nípa àgbọ̀nrín yì fún bí ìsẹ́jú kan. Báwo ni tàbí kílódé tí ó fi jádè wá?

Èyí tí ó jẹ àmìn mẹrin ni ó kọ jáde wá sí àkókò bí ó́ti lẹ̀ jẹ́pé mi kò ri pa. Sùgbọ́n Drenda ti sọ pé òun gbàgbọ́ pé àgbọ̀nrín tí ó tóbí jùlọ ni mà rí pa.

Níbáyìí́, o ti lánfàní tí o ju tèmi lọ. Kì íse ọdẹ àgbọ̀nrín, lójú tiẹ̀, àgbọ̀nrín tótóbi gbọdọ̀ rọrùn láti pa bí ti àwọn yókù nítorí sebí àgbọ̀nrín nà ni gbogbo wọn. Nítorí òun kì imse ọdẹ, kò sì ohun tí ó fẹ́ máa fa àríyaǹjiyàn pé ó séése tàbíkòseése ní tirẹ̀. Èmi kò ti rí irú àgbọ̀nrín tí ó tóbi bẹ́ẹ̀ rí kódà ní ti oniàmì mẹjọ tí mo máa nsọ lórí ilé wa. Tàbí

ibòmíràn. Ó gbàgbọ pé Ọlọ́run le mú wọn wá.

Oko ọdẹ sise yi wáyé ni àkókò tí àwọn àgbọ̀nrín máa bímọ sí, tí wọn pè ni àsìkò gígùn, bẹsìni àgbọ̀nrín le rin ìrìn àjò máilì tó ó bá fẹ́ gùn. Ànfàní máa ńwà ní àsìkò tí wọ́n bá fẹ́ gùn, wà sàdédé rí àwọn akọ àgbònrín lórí ilè rẹ tí wọn ńwá abo kiri, bẹ gan ni ó rí níbiyi.

Ìgbàgbọ́ Drenda ni ó mú àgbọ̀nriń yi jáde wá bíótilẹ̀jẹ́pé èmi kò ní ìgbàgbọ́ fún irú àgbọ̀nrín ńlá yìi.

Mo fẹ́ kí ó lọ kà á lẹ̀ẹ̀kan si —Èmi kò ní ìgbàgbọ́ fún àgbọ̀nrín ńlá!

Mo mọ̀ nkan tí o ńrò—*Dúró ná, Garry. Kò yé mi mọ́. Tí o kò bá ní ìgbàgbọ́ fún àgbònrín ńlá, kíló wá dé ti o fi yọjú wá*?

Bí ọ̀nà kanna tí ọkọ̀ ojú-omi Jákọ́bù àti Jòhánnù na ti se kún nípa ìgbàgbọ Pétérù.

Agbamra alábasepò nìyií.

Jẹ́ kín sọ àpẹẹrẹ kan si fún ọ, kí a wá sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀.

> *Mo ń dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run mi ní gbogbo ìgbà tí mo bá rántí yín: Nínú gbogbo àdúrà mi fún un yín, èmi ń fi ayọ̀ gbàdúrà,* [5] *nítorí ìdàpọ̀ yín nínú ìhìnrere láti ọjọ́ kìn-ín-ní wá títí di ìsinsin yìí. Ohun kan yìí sá à dá mi lójú pé, ẹni tí ó ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rere nínú yín, yóò ṣe àṣepé rẹ̀ títí di ọjọ́ náà tí Jesu Kristi yóò dé:*
>
> *Gẹ́gẹ́ bí ó ti tọ́ fún mi láti ro èyí nípa gbogbo yín, nítorí tí mo fi yín sọ́kàn, bí mo tilẹ̀ wà nínú ìdè tàbí ìdáhùn ẹjọ́, àti ìfẹsẹ̀múlẹ̀ ìhìnrere, <u>gbogbo yín jẹ́ alábápín oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run pẹ̀lú mi</u>.*
>
> —Fílípì 1:3-7

Páúlù sọ pé òun rántí àwọn ìjọ Fílípì pelú ayọ̀ nítorí gbogbo àbásepò yín, tí gbogbo wọn jọ wá ńpín ore ọ̀fẹ́ tí ó wà nínú isẹ́ ìránsẹ́ rẹ̀.

Rántí pé a ti sọ pé ore ọ̀fẹ́ ńrónílágbára tàbí fún ni ní agbára Ọlọ́run tí ó wà lórí Paúlù láti le se àseyọrí isẹ́ rẹ̀? Àwọn ìjọ ní Fịlípì na pín nínú ìnáwó tí isẹ́ nà bí Jákọ́bù àti Jòhánnù na, wọn pín nínú ìfòróróyàn àti ore ọ̀fẹ́ tí ó wà nínú isẹ́ na.

Níbayìí ẹ jẹ kí a lọ sí ìpín kẹrín, àti pé wà rí àwọn èsì tí ó yanilẹnu tí àwọn alábasepọ̀ pèsè.

> *Ṣùgbọ́n ẹ̀yin ṣeun gidigidi ní ti pé ẹ̀yin ṣe alábápín nínú*

> *ìpọ́njú mi. Ẹ̀yin pàápàá sì mọ̀ pẹ̀lú, ẹ̀yin ará Filipi, pé ni ìbẹ̀rẹ̀ ìhìnrere, nígbà tí mo kúrò ni Makedonia, kò sí ìjọ kan ti ó bá mi ń ṣe alábápín ní ti gbígbà àti fífún ni, bí kò ṣe ẹ̀yin nìkan ṣoṣo. Nítorí ní Tẹsalonika ẹ̀yin fi nǹkan ránṣẹ́, lẹ́ẹ̀kan fún àìní mi. Kì í ṣe nítorí ti èmi ń fẹ́ ẹ̀bùn náà: ṣùgbọ́n èmi ń fẹ́ èso ti yóò máa di púpọ̀ nítorí yín Ṣùgbọ́n mo ní ohun gbogbo, mo sì ti di púpọ̀: mo sì tún ni lọ́pọ̀lọpọ̀ nígbà ti mo tí gba nǹkan wọ̀nyí lọ́wọ́ Epafiroditu tí a ti rán wá láti lọ́dọ̀ yín, ọrẹ olóòórùn dídùn, ẹbọ ìtẹ́wọ́gbà, tì í ṣe inú dídùn gidigidi sí Ọlọ́run. <u>Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní yín, gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ rè nínú ògo nínú Kristi Jesu</u>.*
>
> —Fílípì 4:14-19

Paúlù sẹ̀sẹ̀ gba ẹ̀bùn tán kúrò lọwọ́ àwọn ìjọ Fílípì. Tẹ́tísí ohun tí o sọ fún wọn padà. "Ọlọ́run *mi* yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní yín."

Sàkíyèsí pé Paúlù kò sọ pé "Ọlọ́run *rẹ* yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní yín. nítorí tí ó tí lawọ́ śi mi." RÁRÁ! Ó ní, " Níbayìí, Ọlọ́run *mi* yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní yín!"

Sé o ti rí, àwọn ara Fílípì jẹ́ alábasepọ̀ pẹ̀lú Paúlù, àti bí alábasepapọ̀, wọ́n jọ pín nínú ore-ọ̀fẹ́ lóri isẹ Paúlù. Báyìí, bí ti Jákọbù àti Jòhánnù ti rí gbogbo ẹja nítorí ìgbàgbọ́ ti Pétérù, Paúlù wá ńpàsẹ pé gbogbo àìní wọn ni Ọlọ́run yóò pèsè nítori ìgbàgbọ́ *rẹ̀*!

Mo lérò wípé o le rí ànfàní tó wà nínú ìlànà òfin.

Jẹ́ ki á fojú inú wò pé o nílò ọkọ̀, o sì ńse alábasepọ̀ pẹ̀lú wa gẹ́gẹ́ bí ilé isẹ́ ìránsẹ́. Jẹ kí á sọ pé ọ̀kẹ́-kan-àbọ̀ pọ̀ùn ni ọkọ̀ na. Nígbàtí ó wá fúnrúgbìn sínu GarryKeesee.com, ó ní òye ohun tí alábasepọ̀ jẹ́—ó pín nínú ìfòróyàn àti ore-ọ̀fẹ́ tí íse ìránsẹ wa.

Gẹ́gẹ́ bí ilé isẹ́ ìránsẹ́, a le se àdéhùn lórí ọ̀kẹ́-kan-àbọ̀, nítorim a ti kọjá lílo ọ̀kẹ́- kan-àbò pọ̀ùn nị ọjọ́ tó pẹ́. A ní ìgbàgbọ́ fún ọ̀kẹ́-kan–àbò pọ̀ùn bí a sì ti ná mílliọnù lọ́dọdún nísinsìnyí. Sùgbọ́n ní ìgbà kan, mó sì le rántí bí a ti se máa gba Ọlọ́run gbọ́ fún ọ̀kẹ́-kan-àbọ̀ pọ̀ùn, tí o dàbí ọ̀kẹ́- owó ńla kan nígbàna.

Toribẹ̀, bí o bá bimí lérè pé sé mo le gba Ọlọ́run gbọ́ fún ọ̀kẹm-kan-àbọ̀ pọ̀udn níbáyìí, ìdáhùn mi yóò jẹ́ pátápátá bẹ́ẹ̀ni; Torinà, bí Paúlù,

nígbatí a bá wa nínú àdéhùn, tí a sì jẹ́ alábasepọ̀, mo le pàsẹ pé kí Ọlọ́run pèsè fún àìní rẹ, kò ní jẹ́ pé nítori tim ìgbàgbó *tìrẹ* bíkòse ti *èmi*.

Níbayií, ó hàn pé, o ní láti wà nínú ìgbàgbọ nígbàtí o bá nfúnrúgbìn èso ọ̀kẹ́-kan-àbò pọ́ùn, àti pe o ní láti ní ìgboyà kí íse nínú Ọrọ̀ Ọlọ́run nìkan bíkòse nínú wa pẹ̀lú. O gbọ́dọ̀ ni ìgbàgbọ̀ nínú mi, ìgboyà pé ẹni ìfàmìòróróyàn ní mi àti ẹnití Ọlọ́run pè,tí mo sì ńsisẹ́ nínú òtítọ́, kí o sì le rí àfihàn àwọn èsì rẹ̀ nínú ayé mí àti nínú isé ìránsẹ́ mi. Tí o bá wo ohun tí a ńse àti ibití a tí ńbọ̀, o ma ri wípé mo ní ìgbàgbọ́ fún ọ̀kẹ́-kan-àbọ̀ pọ́ùn!

Ìwọ le má ní ìgbàgbọ́ fún ọ̀kẹ́-kan àbọ̀, sùgbọ́n a le sisẹ́ papọ̀ bí alábasepọ̀ àti rí ǹkan tí ó yanilẹ́nu. Bákanna ní fún àgbọ̀nrín tótóbi. Drenda sọ ní alé kín tó jáde ní òwúrò ijọ́ keji, "pé ìwọ gbàgbọ́ fún àgbọ̀nrín, èmi sì gbàgbọ́ fún àgbọ̀nrin ńla." Bí àbasepọ̀ tí ńsisẹ́ nìyì.

Toribẹ̀, jẹ́ kín fi ìdí àwọn òfin kan lé lẹ̀ nípa ìbérè pé: Tí o bá fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ilé isẹ́ kọ̀mpútà, sé ẹnìkan tí kò ní owó tí ó sì jẹ pé ìgbà àkọ́kọ́ rẹ̀ nìyí ní ilé ìwé ìmọ̀jìnlẹ̀ Kọ̀mpútà láti jẹ́ alábasepọ̀ rẹ tàbí wà wá ẹnìkan tí ó ti ní ilé isẹ́ ńla tí ó ti fi míllìọnù dọ́llàr kọ́ ilé isẹ́ oko-òwò kọ̀mpúta tí ó sìtún ní owó làti ran àwọn ilé isẹ́ míràn tí wọn fẹ́ dáśilẹ̀ lówọ́?

Dájúdájú ọ̀pọ̀ àwọn ìyàtọ̀ ni ó wà níbí, mo kàn sì ńse àpejùwe ni. Sùgbọn molérò pé, tí a bá wo, èyítí ó dáju enití wà fẹ́ láti yàn ni ti ẹnití ó ti ní ìrírí, tí ó ní àkọsíle tí ó dájú, tí kò sì ní salàìní! Òtítọ́ yí kanna ni nígbàtí o bá fẹ́ fúnrúgbìn sínú isẹ́ ìránsẹ́ ti alábasepọ̀.

Jọ̀wọ́ má jẹ́ kí ohun tí mò nsọ rú ọ lójú nípa ìdarí Ọlọ́run sí ọ̀dọ̀ enìkan bí alábasepọ̀. Irú ìtọ́ni ti Ọlọ́run yìí ga ju ohun tí mò ńsọ nípa rẹ̀ yìí lọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, ni Ọlọ́run má darí rẹ sí ọ̀dọ̀ alábasepọ̀ pẹ̀lú isẹ́ Rẹ̀, sùgbọ́n nígbàmíràn o ní láti mú ọ̀kan. Mó ńsọ̀ro pàpá jùlọ nípa fúnfúrúgbìn bí ǹkan tí ó yàn látise, Ifúnrúgbìn nígbà ti o bá nílò ìkorè àti sepìnnu pé ó fẹ́ bọ́ sí ìpele míràn tókàn.

Mo fúnrúgbìn sínú isé sise tí mo gbàgbọ́ nínú rẹ̀ fún sísàfihàn idí tí yóò fi yára mú owó tí mo nílò nínú ayé mí wá. Òfin kan tí èmi kì dẹ́ja ni pé mo máa fúnrúgbìn ní gbogbo ìgbà sínú isé síse tí ó ní òye ìgbàgbọ́ àti àdéhùn nígba tí mo bá fẹ́ kí ìkórè mi yára. Irú àwọn ìfífúnni yí máa *sàmìsí* ìfifúnni àti kì ísìse láti jẹ́ kórújú pẹ̀lú fífifún àwọn aláìní.

Fífifún àwọn aláìní jẹ́ ọkàn Ọlọ́run, àdápadà sì wà nínú rẹ̀, sùgbọ́n èmi ńwo ìbásepọ̀ pẹ̀lú isé sise kan tí ó ní ẹ̀rí ti ìgbàgbọ́ tí mo mọ̀ pé ó ní

agbára láti sàdéhùn pẹ̀lú mi.

Ronú nípa rẹ̀ lọ́nà yìí: tí mo bá bi ẹnìkan tí ó ńrí pọ́ùn mẹ́ta ní àrin wákàtí kan tí ó sìtún saláìní tí ó sì ti wà bẹ fún bí ọ̀pọ̀ ọdún láti gbà pẹ̀lú mi fún míllíonù mẹ́wa pọ́ùn, kíni yóò jẹ́ àwọn ànfàní tí àdéhùn gangan tí yóò selẹ̀?

Báyìí, mo le se isẹ̀ ìránsẹ̀ sí ẹnìkẹ́ni, a sì pè mi ni láti se bẹ, sùgbọ́n tí ó bá wá di ti oní àdéhùn, àdéhùn gbọdọ̀ wà. Àgbẹ̀ kan kò kàn ní lọ gbin irúgbìn rẹ̀ sí ibìkan tó bá rí sá tí ó ti dọ̀tí. O má wá ilé tó ní ọ̀rá tí ó le mú irú ìkórè tí ó fẹ́ fún wá. Mo ńsọ̀rọ̀ nípa bíbásepọ̀ lórí ilé ayé pẹ̀lú ìgbàgbọ́ tí elòmíràn, àti ìfòróróyàn ti ẹlòmíràn.

Nkan míràn tí mo ma wá nígbàti mo ba fẹ́ fúnrúgbìn ni isẹ́ ti Ọlọ́run tí o ní irú èso kanna tí mo ngba Ọlọ́run gbọ́ fun ara mi.

Fún àpẹẹrẹ, ilé isẹ́ mi ní ọkọ̀ òfúrufú méjì. Kí ó tó di pé mo ra ọ̀kan nínú wọn Mo ti fúnrúgbìn sí isẹ́ sise tí Ọlọrun, ni ilé isé ìránsẹ tí mo mọ̀ pé o ti sanwó fún dọ́sínnì àwọn ọkọ̀ òfurufú sẹ́yìn ní owó dọ́llàr. Nígbàtí mo bá sọ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀, mọ nsọ pé ni *ọ̀pọ̀lọpọ̀;* tí wọn sì san owó rẹ̀ ni nígbàtí wọ́n rà wọ́n. Tí a bá ńsọ nípa ọkọ̀ ofurufú wọ́n ti se àfihàn rẹ̀ tó pọ̀. Mo mọ̀ pé pẹ̀lú ìrọrùn ni wọn fi le sàdéhùn pẹ̀lú mi tí o bá jẹ ní ti ọkọ̀ òfurufú àti gbàgbọ́ pé yóò wá sí mímúsẹ. Èmi kò níbá ilé isẹ̀ ìrańsẹ ti o sọ pé ọkọ̀ òfurufú ti wọ́n jù sepapọ̀, tàbí tí o sọ pé kò nílò kín ra ọkọ̀ òfurufú , tàbí tí ó sọ pé ti èsù ni kín ra ọkọ̀ òfurufú. Kò sí èyí nínú àdéhùn tí èmi. Rárá, Mo fẹ́ se àdéhùn pẹ̀lú ilé isẹ̀ ìránsẹ̀ tí ó ní òye ibití mo wà tẹ́lẹ̀, tí o sì le bá mi se láti gbàgbọ́ pẹlu mi fún ọkò òfurufú, kín sì rí èso ẹ̀rí rẹ̀.

Mo ti jẹ́ awakọ̀ òfurufú láti ìgbàtí mo wà ní ọmọ ọdún mọ́kàndínlógún tí mo ti kọ́ bí mo ti le fò níwọ̀n ẹsẹ̀ ẹgbẹ̀rún mẹta láti ilẹ̀ jáde ní àwọn orílẹ̀ èdè. Mo máa ńyá àwọn ọkọ̀ òfurufú ni gbogbo ayé mi títí ó fi di ọjọ́ kan tí mo wá ròo pé, *Ó yá, wòó, sé o mọ nkan? Mo kàn fẹ́ fúnrúgbìn irúgbìn kan àti gba Ọlọ́run fún ọkọ̀ òfurufú tèmi*.

Nkan tí mo kàn se ni yìí. Mo mọ irú ọkọ̀ òfurufú tí mo fúnrúgbìn fún, mo kọ irú èyítí mo fé sí ara sọ̀wédowó mi èmi àti Drenda sì jọ sàdéhùn lórí rẹ̀. A sì wá fi sọ̀wédowó nà ránsẹ̀ sí ilé isẹ́ ìránsẹ̀ tí mo sẹ̀sẹ̀ dárúkọ tán.

Osù kan kọjá, mo sì ní dọkítà kan tí mo ní láti lọ rí. Bí mo ti ńbá Dọkítà na sọ̀rọ̀ ni ọjọ́ nà, ó kàn sàdédem sọ pé, “Sé o ti ẹ̀ mọ ẹnìkan tí ó

nífẹ sí láti ra ọkọ̀ òfurufú?”

Ìbéèrè na yà mí lẹ́nu díẹ̀, nítorí mi ò tí rí kí ẹnìkan bi mí lérè irú ǹkan bẹ rí ní gbogbo ayé mí pé bóyá mo mọ ẹnití ó fẹ́ láti ra ọkọ̀ òfurufú. Mo wá bèrè pé irú ọkọ̀ òfurufú wo ni, ó wá jẹ́ irú èyí ti mo fẹ́ tí mo fúnrúgbìn fún.

Ó dájú pé ma fẹ́ láti lọ wo. Mo lọ láti lọ wo ọkọ̀ òfurufú nà, Mo lọ bá ẹnití ó ni, a wa ọkọ̀ na lọ. Ó sì dúró da. Ìsoro kan tí ó wà ni pé—ní ìgbàna, kò sí owó tí mo le fi ràá ní ọwọ́ mị.

Sùgbọ́n Ọlọ́run ní ètò tirẹ̀. Nígbà òjò tí ó kọjá, (osù kẹta ni a wà báyìí), mo ti gba ilem kan ní ọwọ́ Bàbá mi ti mo fẹ sàtúnse rẹ̀ sí ọfísi nígbà òjò. Bàbá mi sọ fún mi pé omi tí mùú kí ó tó di ìgbà òtútù, mi ò tilẹ̀ lọ yẹ wóò.

Kò ju bí ọjọ́ mélo lọ lẹ́yìn na tí àbúrò mi pè mim pé ilé mí nà ti bàjẹ́. Ó tẹ̀síwájú láti sọ fún mi pé gbogbo abala ilé nà ni o ti bàjẹ́, tí ògiri ilé nà sid tún ti wó.

Ó hàn kedere omi na kò wà ní títì àti àwọn òpó omi na ni ó ti di dídì nígbà òtútù. Níbayìí inú osù kẹta ni tí oru ti fẹ́ má mú, omi ti ńyọ nínú ilé tí kò sí ẹnití ó mọ ìgbà tó ti bẹ̀rẹ̀, o fẹ́ to bí ọ̀sẹ̀ mélo.

Ohun tí àbúrò mi kò mọ̀ ni pé mo ti sàdéhùn àti fọwọ́síwe pẹ̀lú àwọn ilé isẹ́ abánikólé láti wo gbogbo ilé nà ní abala na àti nim ẹ̀gbẹ́kan lóde làti túnkọ àti yí ilé nà padà sí ọfisi mi titun.

Nibáyií, ibití ó wá ti sẹlẹ̀ nìyìí: Àwọn ilé isẹ́ adójútòfò ti ní àwọn ma san owó àwọn ibití o ti bàjẹ́, owó yi ni màá sì fi san owó ọkọ̀ òfurufú tí mo fẹ́rà.

Mọ ra ọkọ̀ òfurufú pẹ̀lú owó lọ́wọ́!

Torínà, rántí, pé alábásepọ̀ ni ìlànà òfin tẹ̀mí tí ó ní agbára tí wà fẹ́ láti má kíyèsí àti lo àwọn ànfàní rẹ̀.

ORÍ KẸFÀ

# ÀWỌN OHUN ÌJÌNLẸ TI ÌDÁMẸ́WA

Mo gba àwọn imeelì tópọ̀ léraléra láti le jẹ́ kín mọ̀ pé òfin lórí ìdámẹ́wa ti kọja lọ àti pé kò tún wúlò mọ́.

Bákanna, mo wá ri pé òfin Ìjọba yìí se Pàtàkì ní ó jẹ́ kín fi gbogbo ìpín yìí fún un.

Mo mọ̀ pé, tí o kò bá dé ilé ìjọsìn rí rárá, wà ti gbọ́ nípa ìdámẹ́wa, Sùgbọ́n èmi na mọ̀ pé ohun tí o ti gbọ́ le má wà ní báamu pátápátá, àtipé o sì se Pàtàkì kí a sọ̀rọ̀ nípa ọkàn tí wọ́n ní nípa ìdámẹ́wa ní ìgbà àtijọ́ kín tó má tẹ̀siwájú.

Ní àkọ́kọ́ ju gbogbo rè lọ, tí ó kòbá mọ̀, gbólòhùn yìí ìdámẹ́wa túmọ̀sí pínpín sí ọ̀nà mẹ́wa. A lo ọ̀rọ̀ yí látise àpèjúwe iye tí àwọn ènìyàn Ọlọ́run yóò ma mú wá nínú owó tí ó bá wọlé fún wọn wá fún isẹ́ ti Ọlọ́run, tí ńse ìdámẹwa.

Níbáyií, àlàyé lori ìdámẹ́wa yií jẹ́ ǹkan tí kò le mo sì wá fẹ́ se àlàyè yií jinlẹ̀ nínú àkòrí ti ìpín yìí. Sùgbon báyí tí ǹkan tí mo ńsọ bá jẹ́ ohun titun sí ọ, pàápàá kín ní ìdámẹ̀wa jẹ́ gan, fífi ìdá lọ́nà mẹ́wa fún Ọlọ́run ni.

Ẹlẹ́kejì, ni ọ̀po ìgbàtí àwọn ènìyàn bá ńronú nípa ìdámẹwa, wọn má ronu nípa Májẹ̀mú Láilái àti òfin Mósè níbití wọ́n ti bèrè fún ìdámẹwa ní oríle-èdè Ísráẹlì fún gbogbo ènìyàn.

Lónìí. Ọ̀pọ̀ ohun tó rújú ni ó wà nínú agbo Krístì nípa ìdámẹwa, kín ni ó jẹ́, àti bóyá o sì tún ní ipa kan tó ńkó tàbí ó kúkú ti kọjá lọ pẹ̀lú ìpadàbọ̀ Jésu.

Gẹ́gẹ́ bí o ti má ńgbọ tí mo ma nmsọ pé, nígbàtí Ọlọ́run sọ fún mi láti kọ́ ohun gbogbo tí mo le kọ́ nípa bí Ìjọba rẹ̀ ti se nsisẹ́, mo wá di onímò ìjìnlè t'ẹ̀mí. Mo fẹ́ láti mo ohun gbogbo bí ó ti ńsisẹ́, àti pé ìdámẹwa ni ó

wà di ìbéèrè ńlá tí mo ní láti dáhùn.

Toríbẹ̀ ẹ jẹ́kí á lọ gbé ìdámẹ́wa yẹ̀wò, ibo lóti wá, kín ni ohun tí ó ńse àti kín lódé tí ó fi wà fún òde ònìí. Dájúdájú a rí ìdámẹ́wa bí ohun tí ó se kókó nínu òfin Mose, Láti wá orísun rẹ̀, a ní láti lọ sí idbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ kí a sì ma gbé bí Ádámù àti Éfà.

Gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ sáájú, <u>Adá Ádámù asìfi sọ̀lé ayé bí olórí lórí ilem ayé tí ó dúró fún Ìjọba Ọlọ́run</u>.

> *Ìwọ dá a ní onírẹ̀lẹ̀ díẹ̀ ju àwọn angẹli lọ; ìwọ fi ògo àti ọlá de e ni adé, ìwọ sì fi í jẹ olórí iṣẹ́ ọwọ́ rẹ: Ìwọ fi ohun gbogbo sábẹ́ ẹsẹ̀ rẹ̀."Ní ti fífi ohun gbogbo sábẹ́ rẹ̀.*
>
> —Hébérù 2:7-8a

Afi adé ògo àti ọlá dé Ádámù lórí, àwa kò ì tí ì rí ohun kan tí ó kù tí kò sí ní abẹ́ àkóso rẹ̀. Ohun tí a pè ní *adé* fi àwòrán ńlá kan fún wa bí a ti se le má sisẹ́.

Tí o bá wo ọba kan, tó dé adé, àti, pé olóòtó ènìyàn ni, sùgbọ́n adé orí rẹ̀ fi hàn pé gbogbo ìjọba ńti ọ̀rọ̀ rẹ̀ lẹ́yìn. Bí o ti se rí fún Ádámù ná nìyií. Ó ńjọba lórí ilẹ̀ ayé pẹ̀lú gbogbo àsẹ, tí ọ̀run sì tílẹ́yìn nínú ohun gbogbo tí ó báse. Àwa na gbọdọ̀ rántí pé nínú ara rẹ ènìyàn kan ló jẹ́ tí ó sì ńjọba lórí àsẹ tí a firán. Ó ní ògo (agbára) àti ọlá (ipò àti àsẹ) ti Ìjọba Ọlọ́run tí ó ńtìlẹ́yìn.

Nkan tó yanilẹ́nu, à ti rí Sàtánì lórí ilé ayé nígbàtí a dá Àdámù, bí a ti se le jáde sórí ilé ayé sáajú kí a tó dá ènìyàn. Sàtánì pẹ̀lú bí o ti jẹ́ ẹ̀dá tókéré tó (nínú ayé) tí ó ti jọba lórí rẹ̀ dípò Ìjọba ti Ọlọ́run. Ó fẹ́ wá ọ̀nà tí yóò fi gba àsẹ lọ́wọ́ Ádàmù, kí o ba le sọ pé àsẹ tí Ádámù ńlò kòfẹsẹ̀múlè tó láti máa pàsẹ.

Bẹ́ẹ̀ni, Sàtánì kò ní agbára láti gba ipò lọ́wọ́ Ádámù, toríbẹ ó ní láti dá ọgbọ́n míràn láti tan Éfà jẹ láti jẹ́ kí o gbàgbọ́ pé Ọlọrun kò sem gbékèlem pé kí Efà àti Ádámù sọ̀tẹ̀ sí Ọlọrun láti máa tẹ̀lem òun.

Sàtánì sì se àseyọrí. Ádámù àti Éfà dìtẹ̀ sí Ọlọ́run wọn sì sọ ipò àsẹ wọn nù. Ní àsìkò na, níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pe gbogbo ilé ayé ni o wá lábẹ̀ ìsàkóso Ádámù, Ádámù ti yọ Ọlọ́run kúrò lórí ìsàkóso ilé ayé níwọ̀n ìgbàtí àsẹ tẹ̀mi ti kúrò lọ́wọ́ rẹ, bí ó ti se ya Ọlọrun àti ènìyàn kúrò lọ́dọ̀

Ọlọ́run nìyí.

Ọ̀pọ̀ ohun ni ó selẹ̀ nínú Ẹ̀mí ní àsìkò na, sùgbọ́n mi o ni ́àyè tó láti sọ wọ́n níbayií nítorí ohun tí mo fẹ́ sọ̀rọ̀ lé lórí ní àkòrí wa ìdámẹ́wa. Toríbẹ̀ ẹ jẹ́ kí á padà sí ibití Ádámù àti Éfà ti subú àti rí nkan tí ó selẹ̀.

> *Ọlọ́run sì wí fún Adamu pé, "Nítorí pé ìwọ fetí sí aya rẹ, ìwọ sì jẹ nínú èso igi tí mo pàṣẹ fún ọ pé 'Ìwọ kò gbọdọ̀ jẹ nínú rẹ̀,'"Ègún ni fún ilẹ̀ nítorí rẹ; nínú ọ̀pọ̀ làálàá ni ìwọ yóò jẹ nínú rẹ̀, ní gbogbo ọjọ́ ayé rẹ. Ilẹ̀ yóò sì hu ẹ̀gún àti èṣùṣú fún ọ,ewéko igbó ni ìwọ yóò sì máa jẹ.Nínú òógùn ojú rẹ ni ìwọ yóò ni ìwọ yóò máa jẹuntítí tí ìwọ yóò fi padà sí ilẹ̀, nítorí inú ilẹ̀ ni ati mú ọ jáde wá; erùpẹ̀ ilẹ̀ sá à ni ìwọ, ìwọ yóò sì padà di erùpẹ̀."*
>
> —Génésísì 3:17-19

Ní kía tí a bá wòó, a o ri pé ènìyàn sọ ipò rẹ̀ nù (lé jáde nínú ọgbà ), Èrèdí rẹ̀ wà di bí yóò ti se wá yée, ó wá jẹ́ pé nínú ọ̀pọ̀ làálàá ni ìwọ yóò jẹ nínú òógùn ojú rẹ ni ìwọ yóò ni ìwọ yóò máa jẹun títí. Ọlọ́run tún sọ pé ìwọ yóò sì padà di erùpẹ, pé yóò *kú* ní ọjọ́ kan.

Gbogbo ǹkan wọ̀n yí ni ó sì se àjèjì sí Ádámù, àti ìbẹ̀rù òn àìnírètí tí o wo inú àye rẹ̀.

Mo wá fẹ́ kí a lọ wo Lúkù orí kẹrin.

> *Lójúkan náà, èṣù sì mú un lọ sí orí òkè gíga, ó sì fi gbogbo ilẹ̀ ọba ayé hàn án. Èṣù sì wí fún un pé, "Ìwọ ni èmi ó fi gbogbo agbára yìí àti ògo wọn fún: nítorí á sá ti fi fún mi. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì wù mí, èmi a fi í fún. Ǹjẹ́ bí ìwọ bá foríbalẹ̀ fún mi, gbogbo rẹ̀ ni yóò jẹ́ tìrẹ."*
>
> —Lúkù 4:5-7

Nínu ẹ̀kọ́ yi, Sátánì sọ pé gbogbo owó tí oní se pẹ̀lú ìjọba tí ayé yí (orílẹ̀-èdè) wà lábẹ́ ìsàkóso rẹ̀ ó sì sọ pé àsẹ yí ni a fi fún un. Àti pé òtítọ́ ní o sọ, bí o ti jẹ́ pẹ́ Ádámu ní o fún ni àsẹ na nípasè ìsọ̀tẹ̀ rẹ̀.

Kíyèsí ohun tí o sọ nínú ẹsẹ̀ yí pé gbogbo ọ̀sọ́ orílẹ̀ èdè tàbí ti ìjọba tí ayé yìí wà lábẹ ìsàkóso mí. Ḱín ni ọ̀sọ́ oríleede? *Ọrọ̀* ni.

Gbogbo owó tí o wà lórí ilẹ̀ ayé, bí ìjọba, ti orilẹ-èdè ti fi òǹtẹ̀ tẹ́, toribẹ, gbogbo owó jẹ́ ara ǹkan tí ó wá lábẹ́ ìjọba rẹ̀ láyé. Sàtánì ńsọ pé owó àti ọrọ̀ ti orilẹ̀-èdè ayé wà ní abẹ́ ìjọba rẹ̀, ó sì sọ pé ẹnikẹ́ni ti o ba fẹ́ ni yóò fifún. Níkúkúrú èdè Sàtáni ní òun ni ó ńse ìsàkóso lórí ọ̀rọ̀ àti owó orílẹ̀ èdè. Èyí sí se pàtàkì bí a tise wádi rẹ̀ pé ìdámẹ́wa wà ní èrèdi kan pátó ti ó dájú.

*Adamu sì bá aya rẹ̀ Efa lòpọ̀, ó sì lóyún, ó sì bí Kaini. Ó wí pé, "Pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ OLÚWA ni mo bí ọmọ ọkùnrin." Lẹ́yìn náà, ó sì bí ọmọkùnrin mìíràn tí a pè ní Abeli.*

*Abeli jẹ́ darandaran, Kaini sì jẹ́ àgbẹ̀. Ó sì ṣe lẹ́yìn ìgbà díẹ̀, Kaini mú ọrẹ wá fún OLÚWA nínú èso ilẹ̀ rẹ̀. Ṣùgbọ́n Abeli mú ẹran tí ó sanra wá fún OLÚWA nínú àkọ́bí ẹran ọ̀sìn rẹ̀. OLÚWA sì fi ojúrere wo Abeli àti ọrẹ rẹ̀, ṣùgbọ́n OLÚWA kò fi ojúrere wo Kaini àti ẹbọ rẹ̀. Nítorí náà inú bí Kaini* gidigidi, *ojú rẹ̀ sì fàro.*

*Nígbà náà ni OLÚWA bi Kaini pé, "Èéṣe tí ìwọ ń bínú? Èéṣe tí ojú rẹ sì fàro? Bí ìwọ bá ṣe ohun tí ó tọ́, ṣé ìwọ kò ní jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà? Ṣùgbọ́n bí ìwọ kò bá ṣe ohun tí ó tọ́, ẹ̀ṣẹ̀ ń bẹ ní ẹnu-ọ̀nà rẹ, ó fẹ́ ní ọ ní ìní, ṣùgbọ́n ìwọ gbọdọ̀ ṣe àkóso rẹ̀."*

—Génésísì 4:1-7

Ó dá, kín ni nkan tí ó nsẹlẹ̀ níbiḿyìí? Àwọn yií ni ìran àkọ́kọ̀ ọmọ rẹ̀. Kín ni ìdí ti wọ́n fi nsan ore? Kò sí àkọsílẹ̀ òfin kan tí o sọ pé kí wọn se bẹ ní ìgbàna, kín wa ló dé tí wọ́n fi ńse bẹ?

A le rò pé Ádámù àti Éfà, àwọn òbí wọn, *kọ́* wọn láti máa san ìdámẹ́wa. Àwa na si lérò pé Ọlọ́run kì íse ǹkan fún ìrúbọ pé mo kàn ńse wọ́n atipé wọ́n gbodò ní ìdí kan lábẹ́ *òfin* tí a fi kọ́ Ádámù àti Éfà láti ma san ọrẹ.

Tí o bá wo ohun tí wọ́n kọ, wà rí ìyàtọ̀ ńlá nínu nkan tí àwọn ọmọkùnrin méjéji mú wá. Báyiì, má jẹ́ kí ohun tí wọ́n mú wá sú ọ, ọ̀kán mú ẹran wá àti èkejì mú èso wá, èyí kọ́ ni kókó. Nkan tí ó wà níbẹ̀ nipé *báwo* ni wọ́n ti se ńfi ọrẹ sílẹ̀ àti kílódé tí wọ́n fí ńse àti ìdí tí wọ́n fi sé.

Kíyèsi pé Káiníni mú" díẹ̀" nínú àwọn èso ilẹ̀ wá. Sùgbọ́n Ábẹ́lì mú ẹran tí ó sanra wá fún OLÚWA nínú àkọ́bí ẹran ọ̀sìn rẹ̀." Sé o rí ìyàtọ̀ tí ó wà

nínú wọn? Ní ọ̀dọ̀ ẹnìkan "diẹ̀" ni kí o wá gbéyẹ̀wò sí "èyí tó dárajù" tí ó sanra nínú àkọ́bí ẹran ọ̀sìn rẹ̀?

Kílódé tí Ábẹ̀lì se mú èyí tí ó sanra wá, àti kín ni ó dé tí ó fi jẹ́ láti inú àkọ́bí ẹran?

Ọlọ́run ti le sọ fún Abrahamù àwọn ohun tí wọ́n nílò fún ọrẹ na.

Sé o ti wa ri? Ibi àkọ́kọ́ ti a ti ri ìdámewa nìyìí.

Tí ó bá ka òfin Mósè nípa Ìdámewa, o má jẹ́ **àkọ́kọ́** 10% tí a mú wá láti inu eyí **tó dáraju**. Nínú ìtàn, a le rí kedere pé Ábẹ̀lì fi ìdáméwa sílẹ̀, *àkọ́kọ́* àti èyi tí ó *dára jù.* Bakanna, inú Kaínini kòdùn pé ó fi díẹ̀ sílẹ̀ nínú èso oko rẹ̀ lamti fi ọlá fumn Ọlọ́run o sí pínnu láti mú "díẹ̀" nínum èso ilẹ̀ rẹ̀ wa, kì íse àkọ́kọ́ tàbí èyí tó dárajù.

Ó hàn gédegéde, Káinni mọ̀ kínni àti báwo ni a ti se ńsan ìdámẹ́wa sí Olúwa bí Olọ́run ti sọ fún, "*Tí o bá se ohun tí ò tọ́, sé ò kò ní jẹ́ ìtẹ́wọ́gba? Sùgbọ́n tí ò kò bam se ohun tí ó yẹ, ẹsẹ ǹkan ìlẹ̀kùn rẹ; Ìfẹ́ rẹ̀ láti gba ọ, sùgbọ́n o ní láti jọba lé lórí.*

Sùgbọ́n kaminini kọ ìgbaniníyànjú Ọlọ́run sílẹ̀ láti se nkan tí wọ́n kóó dípò bẹ ó pa Ábẹ́lì, arakúnrin rẹ̀. Ó seése, o ti le rò wípé tí kóbá sí Ábẹ̀lì mọ oun yóò ma se alákóso fún èso ilẹ̀ àti ẹran ọ̀sìn, tàbí kí ó ó jẹ́ ojúkòkòrò rẹ ni ó mú kí ó mú díẹ̀ wá nínú èso rẹ̀, èrò rẹ̀ láti gbọràn sí ọkàn rẹ̀ jìnà sí Ọlọ́run. Mo kàn ńro wò ní. Ohun kan tí a rí nipé Káinni kò fẹ́ má san ìdámẹwa rẹ̀ bí wọ́n ti se kọọ́.

Báyìí, o le máa bèrè, "Kín lódé tí a fi ní láti san ìdámẹ́wa? Kílódé tí Ọlọ́run fi bèrè fún ìdámẹwa? Má dáhùn àwọn ìbérè na, sùgbọn ní àkòkò, ẹ̀ jé kí á wo ǹkan míràn tí a le kọ́ nípa ìdamẹwa kí á tó lọ má dáhùn àwọn ìbérè.

Ní igbà míràn tí a bá rí ti àtún nu sọ̀rò nípa ìdámẹwa á jẹ́ ìgbà àkọ́kọ́ tí a lọ ọ̀rọ̀ yí Ìdámẹwa.

> *Nígbà tí Abramu ti ṣẹ́gun Kedorlaomeri àti àwọn ọba tí ó pẹ̀lú rẹ̀, ọba Sodomu lọ pàdé rẹ̀ ní Àfonífojì Ṣafe (èyí tí ó túmọ̀ sí Àfonífojì Ọba. Melkisedeki ọba Salẹmu (Jerusalẹmu) sì mú oúnjẹ àti ọtí wáìnì jáde wá. Òun ni àlùfáà Ọlọ́run Ọ̀gá-ògo. Ó sì súre fún Abramu wí pé, "Ìbùkún ni fún Abramu ti Ọlọ́run Ọ̀gá-ògo Ẹni tí ó dá ọ̀run òun ayé.Ìbùkún sì ni fún Ọlọ́run Ọ̀gá-ògo*

> *jùlọ, tí ó fi àwọn ọ̀tá rẹ lé ọ lọ́wọ́." Abramu sì fún un ní ìdámẹ́wàá ohun gbogbo.*
>
> —Gẹ́nẹ́sísì 14:17-20

Ìbéèrè tí a nílò láti bèrè nìbíyi: ní báwo ni Ábráhámù ti se mọ láti san ìdámẹ́wà àti pé kínni ìdí?

Ó hàn gbangba pé, Ìdámẹwa yín ti wá di láti ìran dé ìran láti ìgbà Ádámù. A sì wá mọ̀ pé Ọlọ́run ni ó kọ́ Ádámù láti má san ìdámẹ́wa. Òun gan fúnrarẹ̀ lẹ́yìn ìsọ̀tẹ̀. Níbi yi gan ni ati ri ti a lo ìdámẹ́wa, tí ó sàfihàn ìdá lọ́nà mẹwa ohun tí a fún ni.

Ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ni yóò sọ wípé ara òfin Mósè ni ìdámẹwa tí ó túmọ̀ sí pé àwọn onígbàgbọ́ ti Májẹ̀mú Titun kò sí lábẹ́ lílo ìdámẹ́wa. Àwọn ohun méjì tó sẹlẹ̀ tí mo ti sọ, ti Káinni àti Ábẹ́lì àti ti Ábráhámù, fi hàn wá pé ati ńasn ìdámẹ́wa sáajú òfin Mósè, àti pé orílẹ -èdè Ísráẹ́lì na nílò láti san ìdámẹwa. Sùgbọ́n ìdámẹwa wà lára ǹkan tí orílẹ̀-èdè ti ńse kí Mósè tó dé.

Kílówádé tí wọ́n fi kọ ìdámẹwa mọ òfin Mósè? Nígbàtí wọ́n kọ òfin Mósè, Òfin ná wà fún gbogbo orílẹ̀-èdè titun ti Ísraẹ́lì tí ó se jáde kúrò láti orílẹ̀–ède Éjíbítì. Gbogbo òfin àti ohun tí wọ́n nílò ni a ti kọ sílẹ̀ nínú ìwé ìlànà òfin tí ó de gbogbo ènìyàn. Bakanna, ni wọ́n kọ ìdámẹ́wa sínú òfin Mósè láti ri wípé gbogbo àwọn ènìyàn ní orílẹ̀ èdè ni ó ńsan. Ìdámẹ́wa se pàtàkì ti Ọlọ́run se jẹ́ kí wọ́n kọ sínú òfin orile-ede. A wádi tí Ọlọ́run se fẹ́ rí pé wọ́n sé ní kíakía, sùgbọ́n ẹ jẹ́ kí a tún lọ wo àwọn àpẹẹrẹ ti ìdámẹwa diẹ si.

> *Ní ṣinṣin yìí, èyí ni ohun tí* OLÚWA *àwọn ọmọ-ogun wí: "Ẹ kíyèsi ọ̀nà yín. Ẹ̀yin ti gbìn ohun ti ó pọ̀. Ṣùgbọ́n ẹ̀yin kórè díẹ̀ níbẹ̀; Ẹ̀yin jẹun, ṣùgbọ́n ẹ̀yin kò yó. Ẹ̀yin mu ṣùgbọ́n kò tẹ́ ẹ yín lọ́run; ẹ̀yin wọ aṣọ, ṣùgbọ́n kò mú òtútù yin lọ; ẹyin gba owó iṣẹ́ ṣùgbọ́n ẹ ń gbà á sínú ajádìí àpò."*
>
> *Báyìí ni* OLÚWA *àwọn ọmọ-ogun wí: "Ẹ kíyèsi ọ̀nà yín. Ẹ gun orí àwọn òkè ńlá lọ, kí ẹ sì mú igi wá pẹ̀lú yín. Kí ẹ sì kọ́ ilé náà, kí inú mi bà le è dùn sí i, kí a sì yín mí lógo," ni* OLÚWA *wí. "Ẹyin ti ń retí ọ̀pọ̀, ṣùgbọ́n kíyèsi i, o yípadà sí díẹ̀. Ohun tí ẹ̀yin mú wa ilé,*

*èmi sì fẹ́ ẹ dànù. Nítorí kí ni?" ni* OLÚWA *àwọn ọmọ-ogun wí. "Nítorí ilé mi tí ó dahoro; tí olúkúlùkù yín sì ń sáré fún ilé ara rẹ̀. Nítorí yín ni àwọn ọ̀run ṣe dá ìrì dúró tí ilẹ̀ sì kọ̀ láti mu èso jáde. Mo sì ti pe ọ̀dá sórí ilẹ̀ àti sórí àwọn òkè ńlá, sórí ọkà àti sórí wáìnì tuntun, sórí òróró àti sórí ohun ti ilẹ̀ ń mú jáde, sórí ènìyàn, sórí ẹran àti sórí gbogbo iṣẹ́ ọwọ́ yín."*

—Hággáì 1:5-11

Níbiyìí, Wòlíì Hággáì ńba orílẹ̀-èdè Ísraẹlì wí nítorí tí wọn kò tún tẹmípilì kọ́ láti ìgbà tí wọn ti padà dé ní ìgbèkùn Bábílónì. Wọn kò lọsíwájú, wọn wà ní ipò àìní, èrè oko ilẹ̀ wọn kò dára, gbogbo orilẹ̀-èdè wọn ni wọ́n jìyà. Ọlọ́run wa sọ fún orílẹ̀-èdè na láti kíyèsí **ọ̀na wọn**, tó ó túmọ̀ sí pé ǹkankan wà tí wọn ńse tàbí tí wọn kò se tí ó ńfa àìní.

Ọlọrun sọ pé ***"Nítorí yín ni** àwọn ọ̀run ṣe dá ìrì dúró*." Óní Òn sì ti pe ọ̀dá sórí ilẹ̀ nítorí ohun tí ***ẹ̀yín*** ńse. Olúkúlùkù yín sì ń sáré fún ilé ara rẹ̀ nígbàti ilé mi tí ó dahoro. Èyí túmọ̀ sí pé wọn kì Í san ìdámẹ́wa.

Se o ri, Ó yẹ kí wọn mú ìdámẹ́wa wá fún àwọn ọmọ Léfì—àwọn àlufa—àti lọ fún isẹ ìránsẹ ti tẹ́mṕilì. Níwọ̀n ìgbà tí wọ́n kò sì mú ìdámẹ́wa wá fún àwọn ọmọ Léfì, tí wọ́n kò sì tún tẹ́mpilì kọ́, Ọlọ́run ní láti yọwọ́ Rẹ̀ kúrò láti bùkún wọn nítorí ohun tí wọ́n ńse.

Rí dájú wípé óyé ọ kì íse ìfẹ́ Ọlọ́run ni kí ó yọwọ́ àwọn ìbùkún rẹ̀ kúrò ní orílẹ̀-èdè Ísraẹ́lì. Kò sí ohun tí ó fẹ́ se sí, níwọ̀n ìgbà tí ó ti ní ọwọ́ òfin ti ìdámẹ́wa ninú.

Bí a sì ti ńka ìpín kejì, a ri wípé ó séése kí àwọn ènìyàn nà bẹ̀rẹ̀ sí ní gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ tí Wòlíì sọ.

*Ǹjẹ́ nísinsin yìí, ẹ ro èyí dáradára láti òní yìí lọ, ẹ kíyèsi bí nǹkan ṣe rí tẹ́lẹ̀, a to òkúta kan lé orí èkejì ní tẹmpili* OLÚWA*. Nígbà tí ẹnikẹ́ni bá dé ibi òkìtì òṣùwọ̀n ogun, mẹ́wàá péré ni yóò ba níbẹ̀. Nígbà tí ẹnikẹ́ni bá dé ibi ìfúntí wáìnì láti wọn àádọ́ta ìwọ̀n, ogún péré ni yóò ba níbẹ̀. Mo fi ìrẹ̀dànù, ìmúwòdù àti yìnyín bá gbogbo iṣẹ́ ọwọ́ yín jẹ; síbẹ̀ ẹ̀yin kò yípadà sí ọ̀dọ̀ mi,' ni* OLÚWA *wí. 'Láti òní lọ, láti ọjọ́ kẹrìnlélógún oṣù kẹsànán yìí kí ẹ kíyèsi, kí ẹ sì rò ó dáradára, ọjọ́ ti a fi ìpìlẹ̀ tẹmpili* OLÚWA *lélẹ̀, rò*

*ó dáradára: Ǹjẹ́ èso ha wà nínú abà bí? Títí di àkókò yìí, àjàrà àti igi ọ̀pọ̀tọ́ àti pomegiranate, àti igi olifi kò ì tí ì so èso kankan.*

—Hággáì 2:15-19

Níwọ̀n ìgbàtí wọn ti fi tẹmpílì se àkọ́kọ́ lẹ́ẹ̀kansi, Ọlọ́run sọ fún wọn pé kí wọ́n kọ ọjó àti wákàtí nà sílẹ̀ wọ́n yóò rí àyípadà pípọ̀ tí ó yaniléẹ̀nu nínú ọ̀rọ̀ yín. Ó fẹ́ kí wọ́n kí wọn fi àmì sí ojú ibẹ̀ láti le wú wọn lórí àti máa se ìrántí ìyípadà tí ó dé báwọn kí wọn má ba dá ìdámẹ́wa wọn ní sísan dúró. Kì íse fún ànfàní ti ara rẹ̀.

Àwọn kókó ọ̀rọ̀ kan wà níbiyi tí yóò mú ọgbọ́n dání, Sùgbọ́n ohun àkókó nipé, Mo fẹ́ kí ó mọ pé ìdámẹ́wa wà lábẹ́ *òfin.* Ọlọ́run ti yọwọ́ kúrò nígbàtí wọ́n kò san ìdámẹ́wa, kì íse nítorí pé Ó *fẹ́ẹ* bẹ sùgbọ́n Ó ní láti *se* bẹ.

*Èmi* OLÚWA *kò yípadà. Nítorí náà ni a kò ṣe run ẹ̀yin ọmọ Jakọbu. Láti ọjọ́ àwọn baba ńlá yín wá ni ẹ̀yin tilẹ̀ ti kọ ẹ̀yìn sí ìlànà mi, tí ẹ kò sì pa wọ́n mọ́.*

*Ẹ padà wá sí ọ̀dọ̀ mi, Èmi yóò sì padà sí ọ̀dọ̀ yín," ni* OLÚWA *àwọn ọmọ-ogun wí.*

*"Ṣùgbọ́n ẹ̀yin béèrè pé, 'Báwo ni àwa yóò ṣe padà?'*

*"Ènìyàn yóò ha ja Ọlọ́run ni olè bí? Síbẹ̀ ẹ̀yin ti jà mí ní olè."*

*Ṣùgbọ́n ẹ̀yin béèrè pé, 'Báwo ni àwa ṣe jà ọ́ ní olè?'*

*"Nípa ìdámẹ́wàá àti ọrẹ. Ríré ni a ó fi yín ré: gbogbo orílẹ̀-èdè yìí, nítorí ẹ̀yin ti jà mi lólè. Ẹ mú gbogbo ìdámẹ́wàá wá sí ilé ìṣúra, kí oúnjẹ bá à lè wà ní ilé mi, ẹ fi èyí dán mi wò," ní* OLÚWA *àwọn ọmọ-ogun wí, "kí ẹ sì wò bí èmi kò bá ní sí àwọn fèrèsé ọ̀run fún yin, kí èmi sì tú ìbùkún àkúnwọ́sílẹ̀ jáde fún yín, tó bẹ́ẹ̀ tí kì yóò sì ààyè láti gbà á. Èmi yóò sì bá kòkòrò ajẹnirun wí nítorí yín, òun kò sì ni run èso ilẹ̀ yín bẹ́ẹ̀ ni àjàrà inú oko yín kò ní rẹ̀ dànù," ni* OLÚWA *àwọn ọmọ-ogun wí. "Nígbà náà ni gbogbo orílẹ̀-èdè yóò sì pè yín ni alábùkún fún, nítorí tiyín yóò jẹ́ ilẹ̀ tí ó wu ni," ni* OLÚWA *àwọn ọmọ-ogun wí.*

—Málákì 3:6-12 ( NKJV)

Níbíyìí ni a ti rí Wòlíì míràn tí ó ńbá àwọn Orilẹ̀-èdè wí, pé wọ́n ti ja Ọlọ́run lólè agbára Rẹ̀ láti le bùkún àwọn ènìyàn rẹ̀. Ó sọ pé gbogbo orilẹ̀ –èdè ni ó ti wà lábẹ́ ègún nítorí ohun tí wọ́n *kọ̀* láti se. Wọ́n sọ fún wọn láti mú. Ẹ mú gbogbo ìdámẹ́wàá wá sí ilé ìṣúra, kí oúnjẹ bá à lè wà ní ilé mi.

Lẹ́ẹ̀kansi, gbogbo ìdámẹ́wàá ni ó yẹ kí wọ́n mú tọ àwọn ọmọ Léfì lọ, àti àwọn àlufa. Àwọn ènìyàn wá mú díẹ̀díẹ̀ wá kì íse gbogbo rẹ̀ ( Rántí ẹ̀ṣẹ̀ Káinnì). Ọlọ́run ńsọ fún àwọn ènìyàn pé tí wọn bá le mú gbogbo ìdámẹ́wàá wá pé ìbùkún ọ̀run yóò jẹ́ ti wọn padà. Ọ̀run yóò lo ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin láti rìn láàrin wọn. Ọlọ́run sọ fún wọn tí wọ́n ó bá padà sọ́dọ̀ Rẹ̀ pẹ̀lú ìdámẹ́wàá, nígbàna ní irú ìbùkún ti ayé kò ní le gbàá yóò wá sọ́dọ̀ yín.

Ó dára, jẹ́ ki á dánudúró ná, kí á tún sọ̀rọ̀ nípa nkanyi fún bí ìsẹ́jú díẹ̀ kín tó tún tẹ̀síwájú.

Níbáyí a ti rí wípé idámẹ́wa ti bẹ̀rẹ̀ láti àtètèkọ́se, a sì ti rí ìdí rẹ̀ báyi. Níbiyi a ri pé ìdámẹ́wàá gba Ọlorun láye lábẹ́ òfin láti dá sí láàrin ajẹnirun, Sàtánì, àti àwọn ènìyàn Ọlọrun àti bạ sàtánì wí.

Báyii, Ní pàtàki jùlọ, Ọlọrun, "Yọwọ́ Sàtánì kúrò! Sàtáni ò kò le fọwọ́kan ǹkan yìí!

Wòó, nígbàtì subú, Sàtáni kò bá fẹ́ láti mú kúrò lórí ilẹ̀ pátápátá. Sùgbọ́n ní ojúkanna, Ọlọ́run lo ìdámẹ́wa láti fi gba Ádámù adti Éfà. Nígbàtí Ádámù ati Éfà yan ìdámẹ́wa, Wọn ńfi Ọlọ́run se àkọ́kọ́. Ọlọ́run nị wọ́n yàn.

Ẹ jẹ́kí a rántí pé ọ̀nà kanna ní Sàtánì gbà. Nípa yíyí Adámù ati Éfà lọ́kan padà láti gbà á gbọ́ dípò kí wọn gba Ọlọ́run gbọ́, ó gba ọ̀nà ti òfin wọlé. Toribẹ nípa ìdámẹ́wa—fífi 10% fún Ọlọ́run nínú ohun tí o ní—ni o fún Ọlọ́run lẹ́tọ lábẹ́ Òfin láti dá àbò bò Ádamù ati Éfà A nílò láti rántí pé ìdámẹ́wàá jẹ òfin tí ó ńisẹ́ pẹ̀lú ìpèsè ti ènìyàn lórí ilẹ̀ ayé tim ńse agbègbè ti Sàtánì.

**AFI ÌDAMẸWÀ SÍLẸ̀ LÁTI SISẸ́ BÍ ODI LÁBẸ ÒFIN YÍ ÁDÁMÙ ÀTI ÉFÀ KÁ NÍGBÀNA, Ó SÌ TÚN SISẸ́ BÍ ODI LÁBẸ́ ÒFIN BÍ ÀPÁTA ÀBÒ YÍ WA KÁ LÓNÌÌ.**

Kò yí ipò ti wọn wá padà tó ni se níti mí mú àtúnse ohun tẹmi wá. Rárá, ìrúbọ fún ẹ̀sẹ̀ ni akọ́kọ́ gbọdọ̀ se sájú kí o tó sẹlẹ̀. Sùgbọ́n idámẹ́wad gba Ọlọ́run láyè láti dá Sàtánì dúró láti ja wọ́n lólè ìpèsè wọn àti gbà wọn láyè láti yẹ lórílẹ̀ ayé.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn èǹiyàn tí wọ́n sọ wípé idámẹwa jẹ́ òfin ti inú Májẹ̀mú Láiláì tí o sì ti kọjá lọ tí wá sí ìmúsẹ nípa ìrúbọ ti Jésù. A sì ti ri kedere pé Ìdámẹ́wa ti wà ní àyè rẹ sẹ́yìn láti ìgbà ìsubú èǹiyàn kí a tó kọ òfin Mósè.

**Ìdámẹ́wàá ti wà nílẹ̀ láti sisẹ́ bí odi lábẹ́ òfin yí Ádámù àti Éfà ká nígbàna, ó sì tún sisẹ́ bí odi lábẹ́ òfin bí àpáta àbò yí waká lónìí.**

Ìdámẹwàá jẹ òfin lórí ilẹ̀ ayé tí o sì wà nínú ipá agbára níwọ̀n ìgbà tí Sàtánì nì títúsílẹ̀ lórí ilẹ̀ ayé, gẹ́gẹ́ bí o ti wà. Níwọ̀n ìgbà tí Sàtánì bá sì wà níbiyìí, òfin ìdámẹ́wa sì ní ipa lórí rẹ̀.

Ohun míràn tí o tún le má rí nínú ìjọ ni àwọn èǹiyàn tí wọn san ìdámẹ́wa síbẹ̀ wọn kòní ìlọsíwájú. Èyí rí bẹ̀ nítorí àwọn ẹ̀kọ́ òdì tí wọn ti kọ́ nípa ìdámẹwa. Àwọn èǹiyàn tí wọn lérò pé tí àwọn bá kàn ti san ìdámẹwa, Ìbùkún Olúwa yóò kàn mú wọn láti jẹ̀gbádùn àkúnwọ́sílẹ̀ ìlọsíwájú, ju ohun tí wọn le gbà lọ. Nígbàtí wọ́n bá wá bẹ̀rẹ̀ si ni san ìdámẹ́wa tí wọn kò bá ri ìlọsíwájú kí o má kún àkúnwọ́sílẹ̀, wọn yóò pinnu ni ọkan wọn pé ìdámẹ́wa kò sisẹ́. Sùgbọ́n èrò wọn kò se déédé, a sì nílò láti wòó dáda láti wádi kí ló fàá.

Ọlọ́run sọ fún àwọn èǹiyàn pé tí wọn bá san ìdámẹwa.” “*Èmi yóò sì bá kòkòrò ajẹnirun wí nítorí yín, òun kò sì ni* ***run èso*** *ilẹ̀ yín bẹ́ẹ̀ ni* ***àjàrà inú oko yín*** *kò ní rẹ̀ dànù”*

Sé o ri?, Óní Òn yóò sí fèrèsé ọ̀run fún yín, kí sì tú ìbùkún sórí èso *yín.* Òun tí mo ńsọ nibiyii pé o sì nílò láti gbín ǹkan sínú odi ti ìdámẹwa.

Ìdámẹwa gan fúnrarẹ̀ kọ́ ní o mú ọ lọsíwájú. Ó kàn ńdábò bò ńkan tí ó wà nínú odi ni, ìdámẹ́wàam.

Toribẹ tí o bá ní igi èso tòmátò mẹta, àwọn mẹtẹ̀ta ni yóo má se dàdà. Sùgbọn ti ó bá jẹ́ pé gbogbo ohnu tí o ní nà ní igi èso tòmátò mẹ́ta, igi èso mẹta ni yóò di nínlá sùgbọ́n o ma ní ìlọsíwájú to pọ̀.

Ohun tí *o* ba kọ ni yóo ma dàgbà nínú odi rẹ ti yóo mú ọ ní àkúnwọsílẹ̀ pẹ̀lú òpòlọpò.

O banilọkànjẹ́, pèlú ẹ̀kọ́ ti ó lòdì, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn èǹiyàn Ọlọ́run ni wọn ó san ìdámẹ́wa àti fọwọlẹ́ran wọn ó ma retí ọ̀pọ̀ àti àkúnwọ́sílẹ̀. Àkúnwọ́sílẹ̀ yóo bẹ̀rẹ̀ nígbàti a báti se ojúse ti wa na nínú ìlànà yìí.

Toríbẹ̀ lẹ́ẹ̀kansi, ẹ jẹ̀kí a lọ gbéyẹ̀wò.

1. Ìdáméwàá wá sórílẹ̀ ayé ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀, ati nígbà ìsubú èǹiyàn

2. Akọ́ sínú ìwé òfin Mósè nítorí Mósè ni ó ńsọ bí Orílẹ èdè Ísráẹlì yóo se máa gbem. Ọlọrun sì fé rí dájú pé Òn bùkún wọn, àti kọ sínú ìwé òfin kí ó ba le ma tẹsíwájú. Òfin ti ìdámẹ́wa kò tí kọja lọ. Sùgbọ́n gbogbo ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin sí ìdámẹwa ni ó ní. Báyi, á le *yàn* láti san ìdámẹ́wa kí á sì lo ànfàní rẹ̀
3. Òfin ìdámewa ni òfin ni òfin orí ilẹ̀ yóo sì wà bẹ níwọ̀n ìgbà tí Sàtánì wà ní tútúsílẹ̀ .
4. Ìdámẹwa kò le sàdéédé mú ìlọsíwájú wá, sùgbọ́n ó gba Ọlọ́run láàyè láti dá Sàtánì lowọ́ dúró kí ó má dá sí ǹkan tí o ńgbìn tàbí kó nínú odi ìdámẹwa rẹ.
5. Ìdámẹ́wa kò látìlẹhìn lórí pé ó lọ sí ọ̀run tàbí o kò lọ. Wà lọ sí ọ̀run tí o ba pe Orúkọ Olúwa. Sùgbọ́n ìdámẹ́wa yóo ní ipa lórí ìlọsíwájú rẹ lórílẹ̀ ayé.
6. Ilé Ọlọ́run ni ìdámewa wà fún. Nínú Májẹ̀mú Láilái, mo ńtọjú àti fún àwọn àlufa ní oúnjẹ tí wọn sisẹ ní ilé isẹ́ ìránsẹ. Kò sí ìyàtọ lóde òní. Ìdámẹwa yẹ kí ó lọ sí inú ìjọ ni Ọlọ́run ti yan ìdámẹwa láti má mú lọ sí ilé isé ìránsé. Mo ní àwọn ènìyàn tí wọn ma nsọ fún mi pé àwon kò fẹràn ìjọ tí àwọn ńlọ sé àwọn sì le má san ìdámẹ́wa àwọn sibẹ̀. Ìdáhùn mi sí wọn nipé? wá ìjọ míràn èyí ti wọn ti kọ́ ni ní ìgbàgbọ́ àti ìjọba. Tí o kò bá ní ìjọ kan pàtó, o le san ìdámẹ́wa sí ìjọ tí ó ńbọ ọ, sùgbọ́n kí o wá nínú ìjọ tí ó dára tí Ọlọ́run fẹ́. Tí kò bá sí ní àdúgbò rẹ, nígbàna o le san ìdámẹwa sínú ìjọ tí wọ́n ti ńbọ́ ọ.
7. O kò le forukọ si idamewa re. Fun apeere bi o tin san idamewa re, o le so pe, “Mo ńgbin èso ìdámẹ́wa mí fun _____.” Ìdámẹ́wa nà tí ní isẹ́ tí o rán án. O le sọ ọrẹ lorụkọ sùgbọ́n kì íse ìdámẹ́wa.
8. Ìdámewa ni 10% iye tí o nrí. Èyí *sáájú* owó orí. Rántí, Ọlọ́run sọ nípasẹ̀ Málákì, pé, Ẹ mú gbogbo ìdámewà wá sí ilé mi” Ìdámẹ́san kì íse ìdá mẹ́wa. Ìdámẹ́fà kì ise ìdámẹ́wa. “Ìdámẹ́wa ni 10%” tí o bá sọ pé mí ò níle san ìdámẹ́wa sé ohun tí Ọlọ́run sọ fún àwọn ọmọ Ísraẹ́lì láti se nígbàti wọn kò mú gbogbo ìdámẹwa wa: “Fi èyi dán mi wò” ni Ó sọ. Fi ìdámẹ́wa rẹ sílẹ̀ nípa ìgbàgbọ́, Kí o mọ̀ pé Ọlọ́run yóo fi ọlá fún un.
9. Báwo ni mo se le mọ ohun ti ma fi ìdámewa mí dá lé lóri? Òfin àtànpàkò ní èyi: se owó tí ó ńwọlé tásan owó orí lé lórí ni.?

10. Tí ó bá jẹ́ owó osù mi nìkan ni mo nsan ìdáméwa lé lóri. Sé mo le san ìdámẹ́wa lóri oko-òwò mi na? Bákanna, sé mo le sanwó orí lé lórí? Mí ò sì san ìdámẹ́wa lórí gbogbo owó tí nwọlé lórí oko òwò mi. Mó máa fúrugbìn nínú oko òwò mi tí mo bá ti fẹ, sùgbọn èyi kì ise ìdammẹ́wa. Tí o ba fa owó jáde ninu oko òwò mi, ti mo wá san ìdámẹ́wa lóri èyití mo yọ nínú oko òwò mi.
11. Tí mi ò bá ní ìjọ kankan owó ti mo wa yọ ńkọ? O lè san ìdamẹ́wa rẹ sí ibi tí ó tí ńgba ọ̀rọ̀ Ọlọrun àti dàgbà nípa tẹ̀mi títí wà fi rí ìjọ kan. Bẹẹní , ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ni o nro bí ìjọ tí se jìnà sí wọn tóo tí wọn wá se ìsìn lórí afẹ́fẹ́. Tí kò bá sí ìjọ tí wọn gbàgbọ́ nínú Bíbélì ní àyíká rẹ o le san ìdámẹ́wa rẹ sí ìjọ Ọlọ́run tí ó jìnnà. Opọ̀ ènìyàn ni ó wà ni ìgbèríko tí wọn sì ti ńwá sí Faithlifechurch.org ìjọ tó wà ní agbègbè wọn nítori nkan yí gan.

Ó ya, ẹ jẹ́kí á tẹ̀síwájú.

Ọlọ́run fi hàn mi pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Krìstìanì ni wọn ńsan ìdámẹwa wọn bí gbèsè tí wọn jẹ (tí wọn bá ti ẹ̀ san ìdámewa, ọ̀pọ̀ wọn ni kò san). Èyí túmọ̀ sí pé wọn kò tilẹ lo ìgbàgbọ́ wọn rárá nínú ohun tí wọ́n ńse, bíkòse pé wọn sà mọ̀ pé àwọn jẹ ìdámẹ́wa ti wọn ó sì san bí gbèsè ti wọn jẹ.

Ìdíti ó fi dára láti ma san ìdámẹ́wa rẹ, Ó ní láti má san ìdámẹ́wa rẹ̀ nínú ìgbàgbọ́. Láijẹ́bẹ̀, a jẹ́ pé ó fifúnni lábẹ òfin ní kí íse nípa ìgbàgbọ́.

Jẹ́kí gbogbo ọ̀rọ̀ Ọlọ́run jẹ́ ìfihàn ohun tí Ọlorun fẹ́ se sí ọ. Ìdámẹ́wa kì íse ohun ti o wúwo láti gbé, kò sì gbọdọ̀ le láti san. Kí ìse pé Ọlọ́run ńgbìyànjù láti *gba* nkan lọwọ́ rẹ̀, dípò bẹ, Ó gbíyànjú láti jẹ́ kí nkan *dé* ọ̀dọ̀ rẹ̀. Aní láti gbàgbọ́ àti ní oyè àwọn ànfàni tí ó wà nínú ìdámẹ́wa kí a sì ma yọ̀ nínú rẹ̀. Ìdámẹ́wa jẹ́ ara isẹ ìjọsìn tí o kéde pé Ọlọ́run ní orísun rẹ̀. Ó sì ní àwọn ànfàní tí ó dára, nígbàti ó bá san ìdámẹ́wa, a gbọdọ̀ wà nínú ìgbàgbọ́ láti rí gbà.

Mo má nsọ fún àwọn ìdílé láti ní ìdámẹwa wọn lọ́wọ́ nígbàtí wọn bá ti ńbọ̀ wá sí ilé ìjọ́sìn. Mo tún má nsọ pé, kí wọn tó wá sí ilé ìjọ́sin kí wọn ti gbàdúrà sórí ìdámẹ́wa wọn, kí wọ́n sì kéde ànfàní lórí rẹ̀, àti pàsẹ kí fèrèsé ọ̀run sí sílẹ̀ fún wọn kí wọn sì bá Sàtánì wí lórí ìkórè wọn. Wọ́n tún gbọdọ̀ kéde pé Sàtánì kò le já wọn lólè àti pé ohun tí o wà lọ́wọ́ wọn yóò se rere, ní orúkọ Jésù.

Níbáyí, níparim, jẹ kín mú ìjíròrò lórí ìdámẹ́wa wá pẹ̀lú bí ati se kọsílẹ̀ nínú Májẹ̀mú Titun. Oh, bẹ́ẹ̀ni, a ó sọ̀rọ̀ nípa ìdámẹ́wa ní bẹ̀! Nínú ẹsẹ̀ yí ni a ti kà sáajú.

> *Nígbà tí Abramu ti ṣẹ́gun Kedorlaomeri àti àwọn ọba tí ó pẹ̀lú rẹ̀, ọba Sodomu lọ pàdé rẹ̀ ní Àfonífojì Ṣafe (èyí tí ó túmọ̀ sí Àfonífojì Ọba. Melkisedeki ọba Salẹmu (Jerusalẹmu) sì mú oúnjẹ àti ọtí wáìnì jáde wá. Òun ni àlùfáà Ọlọ́run Ọ̀gá-ògo. Ó sì súre fún Abramu wí pé,"Ìbùkún ni fún Abramu ti Ọlọ́run Ọ̀gá-ògo Ẹni tí ó dá ọ̀run òun ayé.Ìbùkún sì ni fún Ọlọ́run Ọ̀gá-ògo jùlọ,tí ó fi àwọn ọ̀tá rẹ lé ọ lọ́wọ́."<u>Abramu sì fún un ní ìdámẹ́wàá ohun gbogbo</u>.*
>
> —Genesisi 14:17-20

Bayii, e je ki a wo ohun ti Heberu so nipa idamewa.

> *Nítorí Melkisedeki yìí, ọba Salẹmu, àlùfáà Ọlọ́run Ọ̀gá-ògo, ẹni tí ó pàdé Abrahamu bí ó ti ń padà bọ̀ láti ibi pípa àwọn ọba, tí ó sì súre fún un, ẹni tí Abrahamu sì pín ìdámẹ́wàá ohun gbogbo fún. Ní ọ̀nà èkínní orúkọ rẹ̀ túmọ̀ sí "ọba òdodo," àti lẹ́yìn náà pẹ̀lú, "ọba Salẹmu," tí í ṣe "ọba àlàáfíà." Láìní baba, láìní ìyá, láìní ìtàn ìran, bẹ́ẹ̀ ni kò ní ìbẹ̀rẹ̀ ọjọ́ tàbí òpin ọjọ́ ayé; ṣùgbọ́n a ṣe é bí ọmọ Ọlọ́run; ó wà ní àlùfáà títí.*
>
> *Ǹjẹ́ ẹ gbà á rò bí ọkùnrin yìí ti pọ̀ tó, ẹni tí Abrahamu baba ńlá fi ìdámẹ́wàá nínú àwọn àṣàyàn ìkógun fún. Àti nítòótọ́ àwọn tí ó jẹ́ ọmọ Lefi, tí o gba oyè àlùfáà, wọ́n ní àṣẹ láti máa gba ìdámẹ́wàá lọ́wọ́ àwọn ènìyàn gẹ́gẹ́ bí òfin, èyí yìí, lọ́wọ́ àwọn arákùnrin wọn, bí ó tilẹ̀ ti jẹ́ pé, wọn ti inú Abrahamu jáde. Ṣùgbọ́n òun ẹni tí a kò tilẹ̀ pìtàn ìran rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ wọn wá, gba ìdámẹ́wàá lọ́wọ́ Abrahamu, ó sì súre fún ẹni tí ó gba ìlérí, láìsí ìjiyàn rárá ẹni kò tó ẹni tí à ń súre fún láti ọ̀dọ̀ ẹni tí ó ju ni. Ni apá kan, àwọn ẹni kíkú gba ìdámẹ́wàá; ṣùgbọ́n níbẹ̀, ẹni tí a jẹ́rìí rẹ̀ pé o ń bẹ láàyè ni."*
>
> —Hébérù 7:1-8

Jọ̀wọ́ sàkíyèsí ohun tí gbólòhùn ọ̀rọ̀ yí sọ "*Ni apá kan, àwọn ẹni kíkú gba ìdámẹ́wàá*" àwọn ọmọ Léfì ni ó ńsọ nínú Májẹ̀mú Láilái. Ó tún tẹ̀síwájum ó ní "*ṣùgbọ́n níbẹ̀,* ***ẹni tí a jẹ́rìí rẹ̀ pé o ń bẹ láàyè ni****.*"

Melkisédékì jẹ́ ọba olóòtọ́, ọba àláàfíà, láijẹ́ pé ó ní ìyá tàbí bàbá, láìsí ìbẹ̀rẹ̀ ọjọ́ àti òpin ayé, ó jọ Ọmọ Ọlọ́run, àlùfa títíláí. Melkisédékì ni Jésù tí ó dúró níwájú Ábráhámù ní ọjọ́ nà. A kò mọ̀ bí Jésù ní àkókò na síbẹ̀síbẹ̀.

Rántí, pem ángẹlì sọ fún Jósẹ́fù láti sọ ọmọ ọwọ́ kùnrin na ní Jésù nígbàti a bí i. Orúkọ Jésù túmọ̀ sí Olùgbàlà, èyí fi hàn fún wa nípa orúkọ Rẹ̀ ẹnití ọ jẹ́ sí wa. Krístì kì ìse orúkọ Jésù ti gbẹ̀yìn. Nígbàtí a bá sọ pé Jésù Krístì, à nsọ pé ẹni àmìòróró Olùgbàlà. A kò sì mọ Jésù nípa orúkọ nà Jésu nígbàtí Ó dúró níwájú Ábráhámù, nítorí a sì tún fi èrò na pamọ́ fún Sàtáni ni àsìkò na.

Toribẹ, Orúkọ Melkisédékì ní orúkọ tí ó hàn tí ńse ọba olóòtọ́ àti Ọmọ Aládé Àláàfíà. Bákana, pẹ̀lú àsọtẹ́lẹ̀, Melkisédékì kede ọjọ́ ọlá Ábráhámù bí ẹnití ó fún ní òunjẹ àti wáìnì, èyí ti a sọ tí májẹ̀mu titun (Àkàrà Ara rẹ̀ tí a bù fún wa àti Wáìnì, ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ tí a fi fún wa) èyí ni a o se pẹ̀lú àwọn àrólé ti Ábráhámù tí ó bá yá àti mú ìlérí Ọlọ́run sẹ èyí ti a ti fi fún Ábráhámù níti àwọn àrólem rẹ̀ nínú Genesisi 12.

Ti a bá sàkìyèsí níti ìdámẹ́wa, àwọn Hébérù sọ pé "ẹni tí a jẹ́rìí rẹ̀ pé o ń bẹ láàyè" ni ó ńgba ìdámẹ́wa náà. Jésù ní ẹni náà tí ó wá ńgba ìdámẹ́wa báyií, ẹni tí a ti jẹrí pé o ńbẹ láàyè! Òn ni Ọba àwọn ọba àti Olúwa àwọn olúwa.

Tóribẹ̀, rántí pé òfin ìdámẹ́wa sì tún ní ipa lónìí. Ohun kan tí ó yípadà na ní àlúfa. Nínú Májẹ̀mú Láilái, àwọn ẹ̀yà Léfì ni wọ́n ńgba ìdámẹwa fún isẹ́ Ọlọ́run. Lónìí, Jésù (tí ó wá láti inú ìran ẹ̀yà Júdà, kì íse Léfì, ni ó se àfihàn àlufa titun tí a ti fi lélẹ̀) ni ó ńgba ìdámẹ́wa láti íjọ Rẹ̀ fún isẹ́ ti isẹ́ ìránsé. Bẹ́ẹ̀ni, Mo mọ̀ pe Jésù gangan kò sí nibiyi tí ó ngba idamewa. Sùgbón rántí Bíbélì sọ pé ìjọ ni ara Krístì, tí ó túmọ̀ sí pé Ó wà níbíyii nípa ti àkọsílẹ̀ òfin gẹ́gẹ́ bí ara ti àwa ná pẹ̀lú tí wà nípa àkọsílẹ̀ ti òfin. Bí ati ńfi fún Ìjọ Rè, ara Rẹ àti fifún Jésù ni. Àwọn ọmọ Léfì, ni abẹ́ májẹ̀mú láiláí,

**ÌDÁMẸ́WÀÁ NI ODI LÁBẸ́ ÒFIN TÍ Ó YÍ AYÉ RẸ KÁ TÍ Ó DÁ Ẹ̀MÍ ÈSÙ DÚRÓ KÍ Ó MÁ LE RÁYÈ JÀ Ọ́ LÓLÈ ÀWỌN ÌPÈSÈ RẸ.**

gba ìdámẹwa nítorí ìsẹ́ ìransẹ ti Ọlọrun.

Bí ati se gbé yẹwò ìdámẹwa jẹ odi yíká ayé rẹ tí ó ńdá ọwọ́ èsù dúrò kí ó má le rí àyè ja ọ lolè ìpèsè rẹ̀. Rántí, ìdámẹ́wa fún ra rẹ̀ kò le mú ọ lọsíwájú! Ìlọsíwájú rẹ ní se pẹ̀lú ohun tí ó nse *nínú* odi!

Ìdámẹ́wa ní òfin tí ó se pàtàkì sì ètò ìsúná ayé rẹ. Ìdí sì nìyí tí mo fi lo àkókò tó pọ̀ láti le sọ nípa òfin pàtàkì ýi ti ìjọba.

Ní ìgbàmíràn tí o bá wà ní ilé ìjọ́sìn àti pásítò wà sọ pé àsìkò tó fún gbígba ìdámẹ́wa, ó yẹ kí o pariwo ayò, nítorí nibayi ó tí mọ̀ àwon ànfàní tí ó rọ̀ mọ́ ìdámẹ́wạ.

ORÍ KEJE

# O NÍLÒ ÀPAMỌ́WỌ́: APÁ KÍNNÍ

Ọ̀kan lára àwọn ọ̀rẹ́ mi pàtàkì, Pásítọ̀ Peter Mortlock. Jẹ́ pásítọ̀ nínú ìjọ City Impact Church ní ìlú Auckland, ní New Zealand. Ó ti kọ́ ilé ìjọ́sìn ńlá kan sí bẹ̀ ó sì ní ọ̀kan nínú àwọn ìjọ Ọlọ́run tí ó tóbi jùlọ ní New Zealand.

Ní gbogbo àsìkò tí a fi ńse ọ̀rẹ́ láti bí ọ̀pọ̀ ọdún sẹ̀yìn, bóyá ní ó tó bi ìgbà ogún tàbí jù bẹ lọ tí ati jọ rin ìrìn–àjò pẹ̀lú alupùpù ní gbogbo Gúúsù Amẹ́ríkà àti ní New Zealand. Òun gan ni ó mú mi ra Harley. Nimtorí Honda ni mo nífẹ sí láti máa gùn fún ọ̀pọ̀ ọdún, Sùgbọ́n nígbàti a lọ sí ìrìn àjò kan ó ní àyàfi kí lọ yá Harley. Fún ìgbà àkọ̀kọ́ mi ó fi taratara nífẹ sí Harley yí bi Honda, sùgbọ́n tí ò bámọ̀ nípa alupùpù Harley, wọn ti se àwọn àyípadà kan lára rẹ̀ bí ọdún díẹ̀ sẹ́yìn, tí mo wá fẹ́ràn. Toribẹ, ní àwọn ọdún ti om kọjá lọ yìí Drenda ra Harley titun kan fún mi tí mo wá fẹ́ràn láti má gbé lọ sí ìrìn àjò.

Ni àsìkò àwọn ìrìn àjò wa, Mo sàkíyèsí pé Pásítọ̀ Peter má ńgbé àpamọ́wọ́ aláwọ kan dání—mo pèé ní àpamọ́wọ́ ti ọkùnrin tí o má ńgbée kọ́ èjìká rẹ̀. Ní ọjó kan mó wá ní egbò nítorí tí mo jókòo lé àpamọ́wọ́ mi, Mo wá bi lérè nípa àpò tí o má ńgbé kọ́ èjìká. Ó dá, ìjíròrò yìí ni ó mú kí ó ra ọ̀kan fún mí ní ọ́jọ́ ìbí mi. Wọn kọ̀ mọ́ wọ́n níbíyìí bí wọn ti se lókìkí tó ní Europu àti ní New Zealand, sùgbọ́n mo nífẹ sí gan.

Tẹ́lẹ̀ gbogbo ìgbà ni mo má nsọ awò ojú mi nù nígbàtí mo bá fi lelẹ̀ ní ibiti mo jókòó sí tí mo sì gbàgbé rẹ̀ síbẹ̀. Sùgbọ́n láti ìgbàtí mo ti ní àpò yìí tàbí ká pe ní àpamọ́wọ́ ti ọkùnrin, ohun tí o rí kí o pèé, láti ìgbàna mi ò sọ ohnukóhun nù mọ́, Ó wá yé mi ìdí tí àwọn obìnrin se fẹ́ràn láti maa gbé àpamọ́wọ́ kiri. Ohungbogbo ni ó wad nínú rẹ̀. Ó dára gan. Báyii, kì se pé

mo nrọ̀ ọ láti ra àpamọ́wọ́ ti ọkudnrin o, mo kàn fẹ̀ dába pé kí o gbé yẹ̀wò.

Sé o mọ̀ pé Jésù sọ fún wa láti máa gbé àpamọ́wọ́ lọ́wọ́.

> *Kí ẹ má sì ṣe lé ohun tí ẹ ó jẹ, tàbí ohun tí ẹ ó mu, kí ẹ má sì ṣe ṣe àníyàn nínú ọkàn. Nítorí gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni àwọn orílẹ̀-èdè ayé ń wá kiri: Baba yín sì mọ̀ pé, ẹ̀yin ń fẹ́ nǹkan wọ̀nyí. Ṣùgbọ́n ẹ máa wá ìjọba Ọlọ́run, gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni a ó sì fi kún un fún yín.*
>
> *"Má bẹ̀rù, agbo kékeré; nítorí dídùn inú Baba yín ni láti fi ìjọba fún yín. Ẹ ta ohun tí ẹ̀yin ní, kí ẹ sì tọrẹ àánú kí ẹ sì pèsè àpò fún ara yín, tí kì í gbó, ìṣúra ní ọ̀run tí kì í tán, ní ibi tí olè kò lè súnmọ́, àti ibi tí kòkòrò kì í bà á jẹ́. Nítorí ní ibi tí ìṣúra yín gbé wà, níbẹ̀ ni ọkàn yín yóò gbé wà pẹ̀lú."*
>
> —Lúkù 12:29-34

Mi ò lérò pé ọ̀rọ̀ ẹ̀sọ́ ara ni Jésù ńsọ níbiyí, bíkòse ìlànà tí ó ní láti yé ọ (ó tún pèé ní àpamọ́wọ́ tí o bá fẹ́.)

Kókó ohnu tí Jésù ńsọ nípe o nílò láti fi àbò bo ìsúra rẹ.

Fún àpẹẹrẹ, mo le ní millliọnù dọ́llàr ní ilé ìfowópamọ́, sùgbọ́n kò sí ore kan tí ó ńse fún mi tí mi ò bá le gbàá láti lòó, àbí bẹ́ẹ̀ kọ́? Ìdí sì nìyìí tí o fi ńgbé àpamọ́wọ́ kiri. Ó jẹ́ ọ̀nà láti ní ẹ̀tọ́ sí dúkìá rẹ.

Tí o ba lọ sọ àpamọ́wọ́ rẹ nù ó jẹ́ ọ̀kan lára ohun tí ò le nìyàn lára tí o le sẹlẹ̀. Mo má ńgbìyànjú láti rí pé kò sẹlẹ̀ bẹ. Àpò mi má ńwà pẹ̀lú mi nígbàgbogbo ni.

Nínú àwọn ọ̀rọ̀ tí Jésù sọ tí mo sọ yìí. A le rí ọ̀rọ̀ ọgbọ́n àti kókó ìlànà òfin ti ìjọba tó ní se pẹ̀lú owọ́ rẹ̀ nínú ìjọba. Àkọ́kọ́ ni, gbólónhùn pe "Má se àníyàn" a si lo gbólóhùn yí ju ìgbà ẹyọkan lo. Jesù sọ fún wa pé Ọlọ́run mọ gbogbo àiní wa ó sì wá sọ ìtọní kan pàtó bí ati se le rí ìpèsè Rẹ ná gbà.

> *Kí ẹ má sì ṣe lé ohun tí ẹ ó jẹ, tàbí ohun tí ẹ ó mu, kí ẹ má sì ṣe ṣe àníyàn nínú ọkàn. Nítorí gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni àwọn orílẹ̀-èdè ayé ń wá kiri: Baba yín sì mọ̀ pé, ẹ̀yin ń fẹ́ nǹkan wọ̀nyí. Ṣùgbọ́n ẹ máa wá ìjọba Ọlọ́run, gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni a ó sì fi kún un fún yín.*

Jésù sọ pé kí ẹ má sì ṣe ṣe àníyàn nítorí gbogbo rẹ̀ ní Ọlọrun ti yanjú: Ọlọ́run mo ohun tí o nílò. Sibẹ́ na Jésù sọ ọ̀rọ̀ kan tí nse ìtọni pé

> *Sùgbọ́n ẹ máa wá ìjọba Ọlọ́run, gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni a ó sì fi kún un fún yín.*

Jésù ńsọ pé Ọlọrun ní ìdáhùn síi, sùgbọ́n ìlànà wà lábẹ́ òfin tí ò fi le rígbà. Ọlọ́run ní ìdáhùn, SÙGBỌ́N o ní lò láti mọ̀ bí ìjọba ti se ńsisẹ́ kí ó tó le rí gbà.

Sé o kíyèsi pé Jésù kò sọ pé kí o kọ́kọ́ wá Ọlọ́run ná *bíkòse ìjọbà Rè*. Mo sì rò pé ọ̀pọ̀ nínú wa ní ó ti túmọ̀ ẹsẹ ìwé mímọ́ yí sí kí o kọ́kọ́ wá Ọlọ́run ná, sùgbọ́n kì íse ohun tí ó sọ nìyíí. Jésù ní kèdere. Tí ó bá jẹ́ wípé wíwá Ọlọrun ní ìdáhùn, kò bá sọ pé "ẹ máa wá *Ọlọ́run* ná, gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni a ó sì fi kún un fún yín." Ọlọ́run mọ ohun tí o nílò, sùgbọ́n àwọn ìgbésè ìlànà òfin kan wá ti o gbọdọ gbé kí ohun tí ọrún ní tó le tẹ̀ ọ́ lọ́wọ́ lórí ilẹ̀ ayé yií.

Jẹ́kí nrán ọ létí pé Ìjọba Ọlọ́run jẹ́ ìjọba pẹ̀lú Ọba, Àsẹ Ọba àti ìfẹ́ Rẹ̀ ní a mú tọ gbogbo àwọn ọmọ ìjọba na wá nípasẹ̀ àwọn alákoso ti òfin ti ìjọba ná.

Nínú gbogbo aẁọn ìwé mí mẹẹ̀rẹrin tí mo ti kọ sáájú lórí ìjọba, mo máa ńfi àsìkò sílẹ̀ láti se àgbéyẹ̀wò nípa ìgbé ayé ní ti Ìjọba, ìgbàgbọ́ àti sàkání agbára. Kín ní ìdí? Nítorí àwọn ìlànà òfin yi sé Pàtàkì fún àseyọrí àti òye rẹ̀ níti ìgbésí ayé tí ìjọba. Mo tí sàlàyé lórí àwọn kókó ti Ìjọba nínú gbogbo ìwé mi nítorí mo mọ̀ pé ọ̀pọ̀ lo le mú ọkan nínú àwọn ìwé yi àti fẹ́ láti mọ tàbí ní ìmọ̀ ohun na tí ó le mú ìyípadà bá ayé rẹ̀.

O ní láti mọ̀ bí Ìjọba ti se ńsisẹ́!

Àwọn àlàyé tí mo ńsọ nínú ìpín yí ni o ti wà nínú àwọn ìwé tí mo ti kọ sẹ́yìn nínú àwọn Yíyí Ètò Ìsúná Padà gbogbo. Tí o ba ti ka ọ̀kan nínú àwọn iwè yìí ó lé kọjá lọ sí orí kẹjọ. Tí o bá ti kà á tí o sì fé mọ àwọn ohun tí ó se Pàtàkì níHnú ìlànà òfin ti ìjọba fara balẹ̀ pẹ̀lú mi nínú orí keje ìwé yìị.

## Òrò Lórí Sàkání-Agbára

Gẹ́gẹ́ bí mo ti bẹ̀rẹ̀ sáájú, mo ńgbé  ní odi ilú lórí ọgọ́ta saarè ilẹ̀ tí ó jọjúgbèsè ní Ohio. Láti ilẹ̀ wa saarè ilẹ̀ márùn-dín-ní-ọgọ́ta ni mo kọ́kọ́ ní, sùgbọ́n ọ̀kan lára àwọn alábágbé mí tún ta ilẹ̀ kan fún mi èyí tí ó pààlà sí ibi ilẹ̀ mí tí o fi wá jẹ́ ọgọ́ta saarẹ̀ ilẹ̀ ní àpapọ̀. A sì ti ńgbádùn ilẹ̀ nà o le ní ọdún mejì-lé-lógun. Aní àwọn igi tí fi le sọdẹ àwọn àgbònrín, bẹ́ẹ̀ni inú irà ti a ti le sọdẹ pẹ́pẹ́yẹ àti orí pápá tí ati le sọdẹ ehoro àti ẹyẹ àpaarò, bákana tí a sì tún le wa ọkọ̀ ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́rin lórí ilẹ̀ na, ìbúkùn ńla ní o jẹ́.

Tị o bá wo ibi tí mò ńgbé, wa rí àkọlé MÁKỌJÁ ÀYÈ RẸ RÁRÁ wà ri àmi yí ní agbègbè kan lórí dúkìá na. Àmí na wà níbẹ̀ kí àwọn ènìyàn ba lé mọ ibití  ilẹ̀ mí ti bẹ̀rẹ̀. Òfin Ohio sọ pé ẹnikẹ́ni tí o bá wọ inú ilẹ̀ mí gbọdọ̀ kọ ìwé lórí rẹ̀ nígbogbo tí wọ́n bá ti wà lóri dúkìá nà. Tí wọ́n kò bá se bẹ, a ó rí wọn bí ẹnití ó ńkọjá àyè rẹ̀ a sì le le wọ́n kúrò lábẹ́ òfin tí wọ́n ó sì tún san ìtanràn àti jìyà ẹsẹ wọn pèlú.

Ní kúkúrú èdè. . .

**O kò le gba sàkání tí o kò lẹ́tọ́ lé lórí lábẹ́ òfin.**

Gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ, lẹyìn ìgbàtí mo bá fọwọ́sí ìwé tí wọn bá kọ nígbàna ní wọn tó ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin láti lo dúkìá mi. Tí ẹnikẹ́ni bá wá bá ọ láti dí o lọ́wọ́ tí wọn bá bèrè pé báwo ní ó ti jẹ́ tí o fi wà lórí dúkìá mi  ìdáhùn rẹ̀ ni pé mo ti sọ fún ọ pé o le sọdẹ  níbè, ìyẹn kò dára tó. Òfin ti sọ fún mi pé mo gbọdọ̀ gba ìwé ti wọn ó fọwọ́sí kín tó le wọlé sí bè.

Bákanna ni tí o bá lọ sí bánkì tí o bá fẹ́ gba owó rẹ; wọn yóò bèrè fún káàdì ìdánimọ̀ rẹ ID. Bẹ sì ní alágbàtà ní ẹ̀tọ́ láti bèrè fún káàdì ìdánimọ̀ rẹ tí ó ba lo káàdì ẹ̀yáwó láti fi ra ọjà. Pé o fi káàdì ìdánimọ̀ rẹ sílẹ̀ kò le dè ọ́ lọ́nà sí àpò òsùnwọ̀n rẹ; ohun tí ó wà fún nà ni láti dá àbò bò ọ́ lọ́wọ̀ àwọn ẹni ibi.

**MỌ OHNU TÍ SE TÌRẸ KÍ O SÌ MỌ̀ BÍ OTI SE LE LÒÓ. GBOGBO ǸKAN WỌ̀NYÌÍ NI A O SÌ FI KÚN  ÚN FÚN Ọ.**

Nígbà tí Jésú sọ pé  kí ẹ kọ́kọ́ wá Ìjọba na. Ohun tí ó nsọ ní pé "*ka òfin ti ìjọba kí o ba le mọ̀ bí o ti se lò ó fi sisẹ́ lábẹ́ òfin àti mú kí ó sisé dáradára lábẹ́ ẹ̀tọ́ tí ó ní gẹ́gẹ́ bí ọmọ ìjọba ti ọ̀run"* Mọ ohun tí se tìrẹ kí o sì mọ̀ bí o ti sele lòó Nígbàna gbogbo ǹkan wọ̀nyìí ni a o sì fi kún ún fún yín.

Àpẹẹrẹ míràn tún ni ti mo bá ńfi owó pamọ́ fún ọmọ mi. Ní kété tí ó bá ti dàgbà tó ti o sì ti bá òfin mu ni wà taari owó nà sínú àsùnwọ̀n rẹ̀. Mo ní láti sọ fún bánki tí ó jẹ́ àti kọ́ ọ bí o ti se le máa gba owó jáde láti inú àsùnwọ̀n rẹ̀ ní bánkì àti bí yóò ti se má fi owó pamọ́. Bíotilẹ̀jẹ́pé àsùnwọ̀n tí o ́wá ̉òfin ni, òun na ni yóò lẹtọ lábẹ́ ìlànà òfin láti máa lòó.

Jẹ́ kin sọ gbogbo ohun tí mo ti sọ ní sókí. Nígbà tí Jésù sọ pé ẹ máa wá Ìjọba Ọlọ́run ná, nkan tí o ńsọ ni kí a kọ bí Ìjọba ti se ńsisẹ́, ó ńsọ nípa àwọn òfin àti ìlànà nínú Ìjọba tí o gbọdọ̀ kọ́ bí wa ti se le gba ohnu tí ńse tìrẹ lábẹ́ òfin gẹ́gẹ́ bí a ti se ri  nínú àsùnwọ̀n bánkì mi fún àpẹẹrẹ, o le ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin sàkáni–agbára lórí àwọn dúkìá kan sùgbọ́n o le má leè gbà á. Nítori tí o tí tẹ̀lé ohun tí òfin sọ bí o ti se le gbà á. Fún àpẹẹrẹ, bí ò bá fi káàdì ìdánimọ̀ rẹ sílẹ̀ ní ilé nígbàti ò ńlọ sí bánkì, o le rí owó gbà jáde nínú àsùnwọ̀n rẹ bí o tilẹ̀ jẹ́ pé  ìwọ ni o si ni owó ́na.

Ní òye ọ̀rọ̀ sàkání–agbára nínú Ìjọba ó jẹ́ ohun àmúyẹ láti se isẹ dáradara nínú Ìjọba.

Mo mọ̀ ó se é se kí o ti gbọ́ ìtàn kan báyi rí: Ẹnìkan tí o mọ rí dáda kò gbádùn, wọ́n wa ní kí a má gbàdúrà fún wọn. Milliọnù àwọn ènìyàn ni wọ́n kóra wọn jọ pọ̀ láti gbàdúrà nítori ẹni na kí ó le gbádùn, síbẹ̀ ẹni na kú. Kílódé?

Tàbí kí ẹnìkan sọ fún ọ pé ìyá àgbà àwọn kú bíótilẹ̀jẹ́pé àwọn gbàdúrà fún wọn, wọ́n sì fẹ́ mọ ohun tó fàá. Tàbí ẹnìkan sọ fún ọ pé àwọn ti fúrúgbìn owó fún nkan tí àwọn nílò owó fún, síbẹ àwọn kò ní owó lọ́wọ́ se àwọn ìdàhùn wà fún irú àwọn ìbéèrè yìí?

Kín to le dáhùn, jẹ́ ki á se bí ẹnití kò mọ nkankan tí o ńlọ nínú ìpele tẹ̀mí, ti mà sì se bí ẹnití kò mọ ǹkankan. Bákanna, ohun tí ́ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ, a mọ̀ pé tí ara ẹnìkan kò bá dá, Jésù ti san ìdíyelé fún ìwòsàn wọn. A sì mọ̀ pé tí bí a bá jẹ ẹnití ó lawọ́ tí o sì se ìfifúnni, Bíbélì sọ pé wọn yóò ri gbà. Síbẹ̀ ní ojojúmọ́, ni a ǹrí àwọn ohun tí ó dàbí ìjákulẹ̀ ninú Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí o dàbí pé kò sisẹ́ bí a ti kọsílẹ̀ ninú ayé ọ̀pọ̀ èniyàn. Sé Ọlọ́run ni ká báwí?.

Gẹ́gẹ́ bí àkọ̀rí tí a jíròrò nínú ìpín yìí, wa ti rí ìdáhùn tí yóò dàbí pé RÁRÁ ni. Tí o bá jẹ́ rárá, kín wá ní ìsoro ibẹ̀? Níwọn ìgbà tó jẹ́ pé ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ní ó ma dá Ọlọ́run lẹbi fún àwọn àjálù tí ó bá dé bá wọn. Wọn mọ̀ pé o ní agbára láti da ibi dúro kí ó má ba sẹlẹ̀ kò sí se bẹ, toribẹ wọn rò wípe Ó *yàn* láti máse bẹ ni. Níbití àsìse ẹ̀kọ́ ti wá nìyìí pé

"Àmúwá Ọlọ̀run ni kí nkan àìda ma sẹlẹ̀ si ́ ènìyàn rere" ibo ló tì wá. Àwọn ènìyàn gbàgbọ́ pé tí kò bá dáwọ ibi dúró tàbí  dásí ọ̀rọ̀ ilẹ̀ nà, Òn ló gbà á láàyè. Sùgbọ́n tí ò bá ní ̀ òye pé Ọlọ́run dára ní gbogbo ìgbà kò sì le sèké, wà mọ̀ pé ìsòro na kò gbọdọ̀ parọ mọ́ Ọlọ́run, Mọ ara rẹ bíkòse níbòmíràn;  wà wá bẹ̀rẹ̀ sí ní  láti rí ìdáhùn.

Tí o wá dàbí ìgbàtí ó bá wọ inú yàrá kan tí ó sókùnkùn, o kò ní sọ wípé àwọn onísẹ́ iná ni ó jà ọ kulẹ̀. Rárá, wà wá ọ̀nà láti tan iná, tí kò bá wá sisé wà lọ láti yẹ gílóbù wò. O mọ̀ pé ó séese ki ́, ó jẹ́ láti ọ̀dọ̀ rẹ.

Tí o bá ní ìmọ ̀ òye pé kò le jẹ èbi Ọlọ́run *láiláì,* bí O ti se fún wa ní ọ̀rọ̀ Rẹ Ọ̀rọ̀ Rẹ àti àwọn ìlérí rẹ tí ó fi ìfẹ Rẹ hàn sí wa, nígbàna ni wa tó bẹ̀rẹ̀ sí ní fọgbọ́n se ìwádi ohun kúkúrú tí o gé ìdáhùn Ọlọ́run kúrò.

Àwọn ọmọ–ẹ̀hìn se àfihàn irú èrò ọkàn yìí nígbàtí wọn kò le dá lé ẹ̀mí àìmọ́ jáde lára ọmọdekùnrin ẹlẹmí èsù kan nínú Mattiu 17:14-23. Dípò kí wọn bèèrè, "Kínni ̀ ìdí tí Ọlọ́run se fẹ́ fi ẹ̀mí aìmọ́ nà síbẹ̀? Wọn bèèrè lọ́wọ́ Jésù, È̀éṣe tí àwa kò lè lé ẹ̀mí èṣù náà jáde?" Èyí ni ó yẹ kí ó ma jẹ́ ìbéèrè wa nígbàtí a bá bá ara wa nínú ipò tí ó tako Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run fún ayé wa.

Toribẹ  lẹ́ẹ̀kansí, ó se pàtàkì pé a gbọdọ̀ mọ̀ pé, lákọ́kọ́, pé Ọlọ́run dára, àti èkejì, pé kì I sèké. O gbọdọ̀ ka Bíbélì kí o sì bèrè ìbéèrè tí ó bá fẹ́ kọ́ bí Ìjọba ti se ńsisẹ́. Rántí, àwọn ìtàn ńláńlá nínú Bíbélì wà níbẹ̀ fún àwọn ìdí kan ni—Jésù ńgbìyànjú láti fi nkankan hàn ọ́.

Ìjọba Ọlọ́run jẹ Ìjọba ti ó nsisẹ́ pẹ̀lú àwọn òfin àti ìlànà tí ò lé yípadà. Àwọn ìlànà òfin yí, bí mo ti se sọ, ni a le kọ́ àti lò gẹ́gẹ́ bí àgbẹ̀ tí ó ní òye ìgbà fúfúrúgbìn àti ìgbà ìkórè ní ilẹ̀ ayé tí ó sì ńlo àwọn òfin wọ̀nyí láti ni ìlọsíwájú. Nítorití ìjọba ńsisẹ nípa àwon òfin, tí ati fi fún gbogbo ọmọ orilẹ̀ èdè láti ni òye rẹ ̀ àti máa lò nínú Ìjọba yí, *ẹnikẹ́ni* ni ó le kọ́ wọn. Nígbà míràn, mo mọ̀ bí àwọn òfin yí tí ńsisẹ́ ó le jẹ́ lárin ìyè tàbí ikú.

Mark àti Hannah wá sínú ìjo wa wọn sì fẹ́ láti bí ọmọ. Títí o fi di ìgbà na, Dọ́kítà ti sọ fún Hannah pé nítorí àwọn ìsòro kan tí ó ní nínú àgọ́ ara rẹ̀, ó le ma se ese fún láti le rí oyún ní dé bi pé yóò bímọ. Sùgbọ́n nígbàtí ó gbọ́ nípa rere Ọlọ́run àti kíkọ́ nípa òfin ti Ìjọba ní ̀ Faith Life Church, ó wá rí pé oun ni oyún. Inú rẹ̀ dùn rékọjá àwọn ọ̀rọ̀. Sùgbọ́n kò pẹ́ púpọ̀, tí ó bẹ̀rẹ̀ sí ní ìrora tí ò le ní inu ikùn rẹ̀, ní àimọye ìgbà ni o le débipé ó ńdákú.

Lẹ́yìn àwọn ìsẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí, Hannah fẹ́ láti se àyẹ̀wò nkan tó nse, toribẹ ó lọ sí ọ́físì Dọ́kítà. Dọ́kítà rẹ kò sí nílẹ̀, sùgbọ́n Dọ́kítà tí ó wà lẹ́nu isẹ́ fẹ́

se àyẹ̀wò ilé ọmọ rẹ̀ fun láti mọ ohun tí ó nsẹlẹ̀ si.

Dọ́kítà yí sì rí ẹ̀jẹ̀ dídì tó tóbi ó wá sọ fún pé oyún nà ti bàjẹ́. Ọmọ na kò mí mọ́.

Dọ́kítà wá sọ fún pé kí ó padà wá ní ọjọ́ kejì ki wọ́n le ba gbé òkú ọmọ na jádè kúrò ní ilé ọmọ rẹ̀, sùgbọ́n Hannah kọ̀ jálẹ̀. Dípò bẹ, Ọkọ rẹ̀ Mark gbàá níyànjú pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti àwọn ìlérí Ọlọ́run àti kí ó ma sọ ìgboyà rẹ̀ nù nínú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nípa ọmọ na.

Ní òpin ọsẹ̀, Hannah gba àdúrà kan nínú ìjọ ó sì ní ìdánilójú pé òun yóò bí ọmọ na ní Àláfíà pẹ̀lú ohun gbogbo tí Dọ́kítà ti sọ fún.

Ni ọjọ́ Ajé ó lọ láti lọ rí Dọ́kítà tiẹ̀ nitorí Dọ́kítà rẹ̀ kò sí nílé nígbà tí ó dúró láti rí Dọ́kítà míràn ní ọjọ́ nà. Dọkità rẹ wá bá dámọ̀ràn láti tún lọ se àyèwò ilé ọmọ lẹ́kànsi. Àyà Dọkità já nígbà tí ó gba èsì àyẹ̀wò na wò, ó wá se kíá láti wo èyí tí o kọ́kọ́ se nígbàtí kò sí nílé ó wá bá Hannah sọ̀rọ̀ pé mo ti wà lẹ́nu isẹ́ yí tó ọgbọ̀n ọdún èmi ò ti rí irú ǹkan yí kó sẹlẹ̀ rí. Mo rí ẹ̀jẹ̀ dídi ní ọ̀sẹ̀ tó kọjá tí o se àyẹ̀wò tí ọmọ kòsí mí mọ́. Bi mo sì ti se nwò o lóní, gbogbo ẹ̀jẹ̀ dídì ti parẹ́, ọmọ tó dápé ni ó sì wà nínú rẹ̀ tí ò si nmí”

Lẹ́yìn bí osù mélo sí ìgbàna, Hannah bí ọmọbìnrin tí ó dápé tí wọ́n sì sọ orúkọ rẹ̀ ní Evelyn. Ní ọjọ́ kan ni ó wá mọ̀ pé ìtumọ̀ orúkọ ọmọ na *ni ìyè*! Bí mo sì ti ńkọ iwé yí lónìí, ọjọ́ Hannah ti súnmọ́ tí yò bí ọmọ rẹ̀ keji báyìí.

Ìtàn tó yanilẹ́nu yìí hàn pé isẹ́ Ọlọ́run ni Sùgbọ́n bí onímọ̀ ìjìnlẹ̀ tẹ̀mí, ó yẹ kí o má ronú nípa àwọn ìbéèrè kan báyìí, bí, Kílódé tí o fi sẹlẹ̀ bẹ? Se Hannah jẹ ọ̀kan lára àwọn tí Ọlọ́run fẹ́ràn jù ni? Sé àbí Ọlọ́run kàn mọ̀ ọ́n mọ̀ yàn láti wo ọmọ na sàn ni Àwọn ìbérè tí ó yẹ kó ní ìdáhùn ni wọ̀n yìí?

Lẹ́ẹ̀kansi, àwọn Krìstìanì kàn, gbà pé ìyanu ni ó sẹlẹ̀, ìyanu tí nsẹlẹ̀ sùgbọ́n mo má ńsọ fún àwọn ènìyàn láti túnnúrò nípa ọ̀rọ̀ yìí “ìyanu” Bí o ti se rí ó túmọ̀ sí nkan tí ó kọjá nkan yẹpẹrẹ, Nínú Ìjọba, síbẹ̀síbẹ̀, èyí jẹ́ bí òfin Ìjọba tí se má ńsisẹ́.

Tí mo bá sọ àpáta kan sílẹ̀, wàá lérò wípé kínni ó se mí tí mo bá wá pariwo pé,“WOW, sé o rí i báyìí? Àpáta na se jábọ́ sílẹ̀! ìyanu ni!” O kò ní gbà pẹ̀lú mi pé ìyanu ni nítorí o mọ̀ pé isẹ́ òfin lálá tóròkè ilẹ̀ ló ńbọ̀ ní, ọ̀nà yí kánna ni ó ńgbà sisẹ́ *nígbàkúgbà* fun. Àpáta yóò ma já bọ́sílẹ̀ *nígbogboìgbà ni.*

Toríbẹ̀, bí onímọ̀ ìjnlẹ̀ tẹ̀mí a gbọdọ̀ ma wá ọ̀nà sí nkan tí ó bá ńsẹlẹ̀ ni,

ní ọ̀nà tẹ̀mí tí yóò fi òfin hàn wá, tàbí àwọn òfin ti Ìjọba tí ó wà nínú ìtàn na.

Ọ̀kan lára ìtàn tó ga jùlọ nínú Bíbélì tí ó le ràn wá lọ́wọ́ láti rí àwọn ìdáhùn kan tó ní se pẹ̀lú ìgbàgbọ́ àti sàkáni-agbára ni a o rí nínú ìwé Lúkù orí kẹjọ

*Bí ó sì ti ń lọ àwọn ènìyàn ko fun ni ààyè. Obìnrin kan tí ó sì ní ìsun ẹ̀jẹ̀ láti ìgbà ọdún méjìlá, tí ó ná ohun gbogbo tí ó ní fún àwọn oníṣègùn, tí kò sì sí ẹnìkan tí ó lè mú un láradá, Ó wá sí ẹ̀yìn rẹ̀, ó fi ọwọ́ tọ́ ìṣẹ́tí aṣọ rẹ̀; lójú ẹsẹ̀ ni ìsun ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ sì ti gbẹ.*

*Jesu sì wí pé, "Ta ni ó fi ọwọ́ kàn mí?"*

*Nígbà tí gbogbo wọn sẹ́ Peteru àti àwọn tí ó wà pẹ̀lú rẹ̀ sọ pé, "Olùkọ́, àwọn ènìyàn ko ní ààyè, wọ́n sì ń kọlù ọ́, ìwọ sì wí pé, Ta ni ó fi ọwọ́ kàn mi?"*

*Jesu sì wí pé, "Ẹnìkan fi ọwọ́ kàn mí: nítorí tí èmí mọ̀ pé, àṣẹ jáde lára mi."*

*Nígbà tí obìnrin náà sì mọ̀ pé òun kò fi ara sin, ó wárìrì, ó wá, ó sì wólẹ̀ níwájú rẹ̀, ó sì sọ fún un lójú àwọn ènìyàn gbogbo nítorí ohun tí ó ṣe, tí òun fi fi ọwọ́ kàn án, àti bí a ti mú òun láradá lójúkan náà. Ó sì wí fún un pé, "<u>Ọmọbìnrin, ìgbàgbọ́ rẹ mú ọ láradá</u>; máa lọ ní Àlàáfíà!"*

—Lúkù 8-42b-48

Nínú ìtàn yìí a rí obìnrin kan tí ara rẹ̀ kòdá fún ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ọdún tí kò sì rí ìwòsàn. Ó sì ńbọ̀ lẹ́yìn Jésù, ó sì fi ọwọ́ kan ìsẹ́tí asọ Jésù lójúkanna ara rẹ̀ sìdá. Báyìí, Àwọn àmì àti mú kí ìjọba sisẹ́ pọ̀ nínú ìtàn yìí tí a le kọ́ tí yóò tan ìmọ́lẹ̀ sí àwọn ìdáhùn tí à ńwam.

Ní àkòkó, gbogbo àwọn ènìyàn tí ó yí Jésù ká ni wọn fi ọwọ́ kàn án, bí ìtàn ti se sọ kódà àwọn ènìyàn nà fẹ́ẹ̀ tì subú bí wọn ti ńti ara wọn. Nígbàtí Jésù bèèrè pé, Tani ó fọwọ́ kàn mí?" Ó ya Pétérù lẹ́nu pé ó ńbèrè irú ìbéèrè yìí, nítorí *gbogbo ènìyàn* ni o ńfi ọwọ́ kan. Sùgbọ́n Jésù sọ pé ẹnìkan ti fọwọ́kàn mí nị ọ̀nà tó yàtọ—Ó mọ̀ pé agbára Ẹ̀mí mímọ́ tí jádè lára Rẹ̀.

Lẹ́yìn tí ó ti ka ìtàn yí tán Orísirisi agogo àti àwọn fèrè ni yó ma dún nínú ẹ̀mi rẹ tí yóò ma sọ fún ọ láti gbé ohun tí ó ńsẹlẹ̀ yẹ̀wò Ọkàn rẹ yóò

wá máa se ìwádi lórí àwọn ìbérè. Gẹgẹ́ bí onímò ìjìnlẹ̀ tẹ̀mí, a ní láti mọ ohun tí ó wo obìnrin ná sàn tí kì fí ise ẹlòmíràn. Mo sì rò pé ọ̀pọ̀ àwọn ẹlòmíràn na ni ó wá níbẹ̀ tí ara ti wọn na kòdá tí wọ́n sì ti ńfọwọ́kan, síbẹ̀ wọn kò wòsàn. Torínà, a ní láti bèrè, "kílódé tí ìfòróróyàn fi sàn lọ sí ọ̀dọ̀ obìnrin yìí nìkan tí kò jẹ́ ẹlòmíràn tí ó fi ọwó kan Jésù ní àsìkò na?"

Àwọn ẹlẹ́sìn ìbílẹ̀ dáhùn pé amú láradá nítorí tí Jésù wòósàn. Sùgbọ́n sé bẹ́ẹ̀ ni? Sé Jésù mọ̀ ọ́n mọ̀ ni láti se isẹ́ ìránsẹ̀ ti ìmúláradá fún ni? Sé ó gbé ọwọ́ le lórí ni? Sé ó pàsẹ fún àìsàn na láti jáde kúrò lára rẹ̀ ni? Ìdáhùn gbogbo rẹ̀ ni rárá. Lótìtọ́, Jésù kò ti lẹ̀ mọ̀ pé obìnrin na wà níbẹ̀. Òn fúnra rẹ̀ bèrè pé tani ó fi ọwọ́ kàn mí.

Toríbẹ, sé Jésù yàn láti mú obìnrin na láradá ní àkókò náà ni? Lẹ́ẹ̀kansí, kò tilẹ̀ mọ̀ pé ó wà níbẹ̀. Báwo ni ó ti se wá rí wòsàn? Kínni ìdí tí o fi rí ìwòsàn? Gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ ìjìnlè nínú Ẹ̀mi, a le sọ pé ó jẹ́ ọ̀kan lára ọmọ Ọlọ́run pàtàkì tàbí ó ní ìbásepọ̀ pàtàkì sí Jèsù, nítorí Ìse Àwọn Àpọ́stélì 10:34 sọ pé Ọlọrun kì ìse ojú sàjú ẹnikẹ́ni.

À sì tún le wò wípé níwọ̀n ìgbàtí Jésù kò tilẹ̀ mọ̀ pé ó wà níbẹ̀, kò sí lárin àwọn tí ó ti pinnu láti wòsàn ní ọjọ́ nà. A le gbà pé Òn ni ó ní ìfòróróyàn, sùgbọ́n kò sí nínú ìpinnu rẹ̀ láti mú *obìnrin* na láradá ní àkókó na.

Jésù sọ fún wá gan bí o ti gbá àsẹ àti agbára ti Ìjọba mú. Ó sọ pé *"Arabinrin, igbagbo re mu o larada. Ma lo ni alaafia"* Gbólóhùn ọ̀rọ̀ yí ti sọ ohungbogbo tí a nílò láti mọ̀ àti àwọn ìdáhùn sí àwọn ìbérè yí sí ọ le jẹ́ kílódé àti báwo tí o fi rí gbà ní ọjó nà. Gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ ìjìnlẹ̀ tẹ̀mí, jẹ kí á wá fojú inú wo ìtàn yí dáda àti rí bóyá a lè rí àmì kan tí ó le fi ìdí tí a fi mú láradá hàn.

Lákọ́kọ́, Jésù pè ní ọmobinrin, tí ó túmọ̀ sí pé ara Ísraẹlì ní se, irú ọmọ Ábráhámù. Gẹ́gẹ́ bi ọmọ Ábráhámù, ó ti gba ìbùkún tí a fi fún Ábráhámù àti àwọn ànfàní ti májẹ̀mú ti Ọlọ́run dá pẹ̀lú Ábráhamú.

> *Ó wí pé, "Bí ìwọ bá fetísílẹ̀ dáradára sí òfin* OLÚWA *Ọlọ́run, ti ìwọ sì ṣe ohun tí ó tọ́ ni ojú rẹ̀, ti ìwọ sì tẹ̀lé ohun tí ó pàṣẹ, ti ìwọ si pa ìlànà rẹ̀ mọ́. Èmi kì yóò jẹ́ kí èyíkéyìí nínú àwọn ààrùn wọ̀n—ọn—nì ti mo mú wá sórí àwọn ará Ejibiti wá sí ara rẹ, nítorí èmi ni* OLÚWA *ti ó mú ọ láradá."*
>
> —Ẹkísódù 15:26

Nígbàtí Jésù pèé ní ọmọbìnrin, ó túmọ̀ sí pé o ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin sí gbogbo májẹ̀mú ti Ọlọ́run bá Ábráhámù dá. Sùgbọ́n òótọ́ yí nìkan kò le mú kí ó jẹ́ pé ní ìdí tí o fi rí gbà, bí gbogbo àwọn ènìyàn tí ó wà níbẹ̀ lọ́jọ́ nà tí wọ́n fi ara ti Jésù ní ẹ̀tọ́ yí kan na. Nkankan gbọdọ̀ wà tí ó mú kí agbára ti Ìjọba Ọlọ́run sàn. Jésù na sì sọ ìdí míràn kan tí ó fi rí gbà fún wa Kódà, Jésu sọ pé èyí gan ní ohun tí ó fàá tí òun gan fi rí gbà.

O ní *ìgbàgbọ́ rẹ̀* mu láradá.

Níbayi a ti mọ ìdí tí ó fi le gba ìmúláradà—ó jẹ́ ẹ̀tọ́ rẹ̀ lábẹ́ òfin láti gbàá níwọ̀n ìgbà tí ó jé ọmọbìnrin ti Ábráhámù, ti ìgbàgbọ rẹ̀ sí jẹ́ okùnfà tí ó mú agbára na sàn lọ śinú àgọ́ ara rẹ̀ ní àsìkò nà gan.

Nítorí tí ó jẹ́ ọmọbìnrin rẹ̀ a le fi wé ilẹ isẹ́ agbára tí ó ní agbára na ní títàn tí ó sì ti fa okùn iná nà wolé rẹ̀. Agbára wạ, sùgbọ́n èyí kò túmọ̀ sí pé iná rẹ̀ yóò wa ̀ní títàn. Ìwọ gan ní láti tẹ̀ ẹ́ kí iná tó le tàn.

Toribe, bí ìran Ábráhámù ti ó ní ẹ̀tọ́, ọmọbìnrin yi lẹ́tọ́ lábẹ́ òfin láti wòsàn. Síbesíbẹ̀, nítorí ó ní sàkání-agbára lórí ilẹ̀ ayé àti lórí ara rẹ̀, ó ní láti tan iná nà fún ara rẹ̀ láti le tú agbára sílẹ̀.

Sùgbọ́n níbo ní ohun tí yóò fi tanná wá? Báwo ni yóò ti se tan iná nà?

Láti le mọ̀, a nílò láti sọ nkan tí a fẹ.

## Kín ni ìgbàgbọ?

Ìgbàgbọ́ ni ohnu tí àwọn Krìstíánnì má jù kiri ní àyíká laí lákàsí, àti pé mo sì mọ̀ dájú pé ọ̀pọ̀lọpọ̀, tí kì bá se gbogbogbo, ni kò mọ ohun tí ìgbàgbọ́ jẹ́, kí lódé tí a fi nílò rẹ̀, báwo ní o ti se le mọ̀ tí wọ́n bá wà nínú ìgbàgbọ́, àti pé báwo ni ati se le gba ìgbàgbọ́. Tí ìgbàgbọ́ bá jẹ́ nkan tí a tẹ̀ tí ó mú kí ìfòróróyàn má sàn àti mú obìnrin ýi láradá, a ní láti gbé ìgbàgbọ́ yẹ̀wò dada!

Arí ìtumọ̀ ìgbàgbó wa nínú Rómù 4.

> *Nígbà tí ìrètí kò sí mọ́, Abrahamu gbàgbọ́ nínú ìrètí bẹ́ẹ̀ ni ó sì di baba orílẹ̀-èdè púpọ̀, gẹ́gẹ́ bí èyí tí a wí fún un pé, "Báyìí ni*

> *irú-ọmọ rẹ̀ yóò rí." Ẹni tí kò rẹ̀wẹ̀sì nínú ìgbàgbọ́, nígbà tí ó mọ pe ara òun tìkára rẹ̀ tí ó ti kú tan, nítorí ó tó bí ẹni ìwọ̀n ọgọ́ọ̀rún ọdún, àti nígbà tí ó ro ti yíyàgàn inú Sara: Kò fi àìgbàgbọ́ ṣiyèméjì nípa ìlérí Ọlọ́run; ṣùgbọ́n ó lágbára sí i nínú ìgbàgbọ́ bí ó ti fi ògo fún Ọlọ́run; <u>Pẹ̀lú ìdánilójú kíkún pé</u>, Ọlọ́run lè ṣe ohun tí ó ti ṣe ìlérí rẹ̀.*
>
> —Rómù 4:18-21

Ẹ jẹ́kí ágbẹ̀kalẹ̀ ìtàn yí kó yé wa. Ábráhámù àti Sáràh kò le bímọ. Èmi ò sọ pé wọn ní ìsòrò àti bímọ tí wọ́n wá ńgbìyànjú. Mo ní wọn ti tó ẹni ọgọ́ọ̀rún ọdún, jù bẹ lọ. Ara wọn kò le gbé ọmọ mọ; kò séese fún wọn! Síbẹ̀ Ọlọrun sèlérí fún Ábráhámù pé yóò bí ọmọ tí ó bá jẹ́ ni ti ènìyàn, kò lé séése mọ́.

Bíbélì sọ pé Ábráhámù *Pẹ̀lú ìdánilójú kíkún* pé Ọlọrun ní agbára àti se ohun tí ó bá sọ pẹ̀lú ohun yówù tí ó jẹ́ tí o le má sọ ìtàn tí ó yàtọ̀. Èyí nì ìtumọ̀ ìgbàgbọ́ wa: kún pẹ̀lú ìdánilójú pem Ọlọ́run ní agbára láti mú ohnu tí ó bá sèlérí se.

Mo kọ́ sílẹ̀ báyi pé; "**Ọkan rẹ wà nińú àdéhudn pẹ̀lú ọ̀run**" kì íse kí o gbà ní ọkàn rẹ pẹ̀lú ohun tí Ọlọ́run sọ bíkòse pé *Pẹ̀lú ìdánilójú kíkún.*

## Ìtumọ̀ ohun tí ìgbàgbọ̀ jẹ́

Pariwo sókè sọ pẹ̀lú mi láti le mọ̀ dájú pé ó yé ọ: Ìgbàgbọ́ ni Pẹ̀lú ìdánilójú kíkún ohun ti Ọlọrun sọ. Ọkàn wa àti ẹ̀mi wa nínú àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run, *Pẹ̀lú ìdánilójú kíkún*

## Kínni ìdí tí a fi nílò ìgbàgbọ́?

Kílódé tí Ọlọ́run kò se wo gbogbo àwọn tí ó wà ní ilé ìwòsàn sàn, nígbàtí ó bá fẹ́ sem? Kílódé tí kò se fi dá àwọn ogun dúró? Kílódé tim kò fi rán àwọn ángẹli láti wàásù ìhìnrere fún wa? Mo mọ̀ dájú pé o ti gbọ́ gbogbo irú àwọn ìbéèrè yí rí tẹ́lẹ̀. Ìdáhùn ni wípé Kò le se bẹ.

Kì íse pé Ọlórun kò ní agbára láti se bẹ. Kò ní *sàkání–agbára* láti sé ni.

Láti ní òye ńkan tí mo ńsọ, a ní láti lo wo inú ìwé Hébérù.

> *Ṣùgbọ́n ibìkan wà tí ẹnìkan tí jẹ́rìí pé:*
> *"Kí ni ènìyàn tí ìwọ fi ń ṣe ìrántí rẹ̀, tàbí ọmọ ènìyàn, tí ìwọ fi ń bẹ̀ ẹ́ wò? Ìwọ dá a ní onírẹ̀lẹ̀ díẹ̀ ju àwọn angẹli lọ; ìwọ fi ògo àti ọlá de e ni adé, ìwọ sì fi í jẹ olórí iṣẹ́ ọwọ́ rẹ: Ìwọ fi ohun gbogbo sábẹ́ ẹsẹ̀ rẹ̀."*
> *Ní ti fífi ohun gbogbo sábẹ́ rẹ̀, ṣùgbọ́n àwa kò ì tí ì rí ohun kan tí ó kù tí kò sí ní abẹ́ àkóso rẹ̀. Síbẹ̀ nísinsin yìí àwa kò ì tí ì rí pé ó fi ohun gbogbo sábẹ́ ìṣàkóso rẹ̀.*
>
> —Hébérù 2:6-8

Ọlọrun fún ènìyàn nim ẹ̀tọ́ lórim sàkání agbára lórí gbogbo ilé ayé nígbà tí ó fi wọ́n síbẹ̀. Kò sí ohun kan tí kò sí ní sàkání rẹ̀. Ó njọba lórí ilẹ̀ ayé pẹ̀lú agbára àti àsẹ ni, Agbára rẹ̀ láti jọba pẹ̀lú àsẹ ni ó ní àtìlẹ́yìn ti ìjọba tí ó gbé síbẹ̀. Ní Pàtàkì jùlọ ó ńjọba pẹ̀lú àwọn asojú àsẹ tí ìjọba ọ̀run. Ó dé adé ti ìjọba na, èyí tí ó dúró fún ògo ti Ọlọ́run, ìfòrórόyàn, àti ipò ọlá tàbí àsẹ tí o ní.

**ỌRUN KÒ NÍ SÀKÁNÍ–AGBÁRA LÓRÍ ILẸ̀ ÀYÀFI, ỌKÀN ỌKÙNRIN TÀBÍ OBÌNRIN PẸ̀LÚ ÌDÁNILÓJÚ KÍKÚN OHUN TÍ ỌRUN SỌ, TÍ À ŃPÈ NÍ ÌGBÀGBỌ́.**

Níbayi, lóòtọ́, kò dé adé tí a fi irin se, sùgbọ́n ó dé adé níti òye ohnu tí adé dúró fún. Láti le rí àwòrán ohun tí mo nsọ bóti rí fojú inu wo ọba kan. Bíotìlẹ̀jẹ́pé ènìyàn ni tí kò sì ní agbára kan bí ènìyàn, ó dé adé, tí ó fi hàn pé ó dúró bí asojú kí se fún ara rẹ̀ nìkan bíkòse fún gbogbo agbègbè àti ìjọba. Awọn ọ̀rọ̀ rẹ̀ sì ní àsẹ nínú nítorití ó ní àtìlẹ́yìn agbára àti ohun àbáláyé tí ìjọba àti ìjọba tí ó dúró fún.

Tí o bá ronú pé òsìsẹ́ agbófinró kan ní o ńdarí sumnkẹrẹ-fàkẹrẹ àwọn ọkọ̀, yóò dá katakata kọ̀ akẹ́rù ńlá dúró pẹ̀lú kí ó sọ pé "dúró" ní orúkọ tí ofin!"

Bẹ̀ẹ̀ni, ọkọ̀-akẹ́rù yí tóbi ju ọkùnrin na lọ, ọkùnrin yim gan fúnrarẹ̀, mọ̀ pé òun kò tó ọkọ̀ akẹ́rù. Sùgbọ́n ọkọ̀-akérù yìí dúró kì íse nítorí ọkùnrin na súgbọ́n nítorí àmì tí ó wà lára ohun tim ọkùnrin na wọ̀, tí o

dúró fún ìjọba tí ó ńtìlẹ́yìn. Ní ibi yí, ìjọba wá tóbiju ọkùnrin na lọ tí o ní báàji tí ńse àmì ti ìjọba. Níti awakọ̀ akẹ́rù yi, wọn kò ní ìbẹ̀rụ̀ *ọkùnrin na,* sùgbọ́n wọ́n bẹ̀rù ìjọba ti arákùnrin na se asojú fún, torinà ó dá ọko akẹ́rù na dúró. Òtítọ kanna ni nim ibíyìí. Ádámù jọba lórí ohun gbogbo tí Ọlọ́run dá sórim ilẹ ayé. Agbára Ọlọ́run àti ìjọba rẹ̀, dúró fún adé àti ògo àti ọlá, tí ó fún ènìyàn ní irú ìdánílójú pé àwọn ọrọ̀ rẹ̀ jọba dípò Ìjọba Ọlọ́ruṇ.

*Ọ̀run àní ọ̀run ni* ***ti*** *Olúwa: ṣùgbọ́n ayé ló* ***fi fún ọmọ ènìyàn.***
—Orin Dafidi 115:16

Ìlànà òfin sàkání–agbára ènìyàn lórí ilé ayé se Pàtàkì sí òye rẹ ni ti òfin Ìjọba, pàpá jùlọ níbíti ó ti nílò ìgbàgbó fún Ọlọ́run láti gba sàkáni ipò na.

> *Nígbà náà, Jesu wí fún wọn pé, "A máa ń bu ọlá fún wòlíì níbi gbogbo àfi ní ìlú ara rẹ̀ àti láàrín àwọn ìdílé àti àwọn ẹbí òun pàápàá." Nítorí àìgbàgbọ́ wọn,* ***<u>òun kò lè ṣe iṣẹ́ ìyanu ńlá láàrín wọn,</u>*** *àfi àwọn aláìsàn díẹ̀ tí ó gbé ọwọ́ lé lórí, tí wọ́n sì rí ìwòsàn. Ẹnu si yà á nítorí àìgbàgbọ́ wọn. Lẹ́yìn náà, Jesu lọ sí àárín àwọn ìletò kéékèèkéé, ó sì ń kọ́ wọn.*
>
> —Maaku 6:4-6

Tí mo bá bi àwọn ènìyàn ní òpópónà pé tí Jésù bá le se ohungbogbo, Wọn yóò kúkú dámilóhùn pé ohun gbogbo ló lè se. Tí mo bá wá bèrè pé ǹjẹ́ arí ibìkan nínú Bíbélì ti Jésù ti gbìyànjú tí kò sí rí isẹ́ ìyanu se, kín wọn ó wí?

Mo mọ̀ dájú pé ohun tí wọn ó sọ fún mí nipé kò sí nínu Bíbéli ibití Jésù ti gbìyànjú àti se isẹ́ ìyanu tí kòsì ri se, síbẹ̀ ó sẹ̀sẹ̀ ka ọkan tán ni. Jésù kò le mú gbogbo wọn láradá. Gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ijínlẹ̀ tẹ̀mí, mo fẹ mọ ìdí rẹ̀.

Ìdáhùn rẹ̀ rọrùn ohun na ni wípé—kò le sé, àti pé ó ti mọ̀ nísisìyí pé nítorí tí wọn kò ní ìgbàgbó ni. Kò sí àdéhùn pẹ̀lú ọrun, torínà kò sí ní òfin tó de ọ̀run láti dá sí ipò na.

Rí dájú pé o ní òye tókún nípa ohun tí a sàwári yií.

**Ọ̀run kò ní sàkání–agbára lórí ilé ayé, àyàfi ọkàn ọkùnrin tàbí ti obìnrin Pẹ̀lú ìdánilójú kíkún ohun ti ọ̀run sọ, tí ńse ÌGBÀGBỌ́.**

Bí àpẹẹrẹ ti a ti sáájú, ẹ̀nìkan tí o mọ rí dáda kò gbádùn, wọ́n wa ní kí a má gbàdúrà fún wọn. Milliọnù àwọn ènìyàn ni wọ́n kóra wọn jọ pọ̀ láti gbàdúrà nítori ẹni na kí ó le gbádùn, síbẹ̀ ẹni na kú. Sé Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run kùnà ni? Rárá Ìyẹn kò le séese. Torínà a ní láti rí ìdáhùn wá níbòmíràn.

> *Ṣùgbọ́n nígbà ti ẹ̀yin bá ń gbàdúrà, ẹ má ṣe àtúnwí asán bí àwọn aláìkọlà, nítorí wọn rò pé a ó tìtorí ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ gbọ́ tiwọn. Ẹ má ṣe dàbí i wọn, nítorí Baba yín tí ń bẹ ní ọ̀run mọ ohun tí ẹ ṣe aláìní, kí ẹ tilẹ̀ tó béèrè lọ́wọ́ rẹ̀.*
>
> —Máttíù 6:7-8

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ni ó gbàgbọ́ pé bí àwọn ènìyàn bá ti pọ̀ tó tí wọn ńgbàdúra, jẹ́ ànfàní ńlá fún Ọlọ́run láti gbọ́ àti mú kí ó le se ìrànwọ. Mo lérò pé mọ ti sọ ọ̀pọ̀ àlàyé fún ọ láti jẹ́ kí ọmọ pé irọ́ pátápátá ni. Nígbàtí mo ba sì sọ pé wọ́n kò ní ìgbàgbọ́, ohun tí mo sì ńsọ na ni pé ẹni tí ó nílò láti gba nkan lọ́wọ́ Ọlọ́run kò ní ìgbàgbọ́. Ó ní láti gbà pẹ̀lú mí pé Jésù ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbàgbọ́ nínú àwọn ìtàn tí a ti sọ nínú ìwé Mákù orí 6 síbẹ̀ kò le wo gbogbo wọn sàn.

Toribẹ tí èmi àti ìwọ bá jọ ńsọ̀rọ̀ nípa ọ̀rẹ́ tí ara rẹ̀ kò dá pẹ̀lú milliọnù àwọn ènìyàn tí ó ńgbàdúrà fún wọn, mà le bi ọ́ lérè pé" Kínni *òun* (ọ̀rẹ́ tí ara rẹ kòdá) *ńsọ*?"

A le ní *bílliọ̀nù* lọ́nà ogún àwọn ènìyàn kí wọn ma gbàdúrà fún ẹnìkan tí ara rẹ̀ kòdá, sùgbọ́n tí aláìsàn na bá ńsọ pé òun yóò kú ni, irú ẹni bẹ yóò kú.

Ẹ jẹ́ kí á lọ gbé àpẹẹrẹ wa ti inú Mákù orí kẹfa yèwò lẹ́ẹ̀kansi. A mọ pé Jésù ni ìgbàgbọ́ láti wòsàn Sùgbon kò le se ohunkóhun fún àwọn ènìyàn láijẹ̀ pé wọ́n lo ìgbàgbọ wọn.

Mo ti rí ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn tí wọ́n ti wá sọ́dọ̀ mi tí wọn se àlàyé bí ara ìyá àgbà tàbí bàbá àgbà tàbí ìbátan wọn tí ara wọn kòdá tí wọn sì ti gbàdúrà títí fún wọn, síbẹ̀ kòsí nkankan tí ó sẹlè. Gbogbo ìgbà ní mo máa ńbèèrè pé, Kín ní ìyá àgbà ńsọ? Kínni bàbà àgbà na ńsọ? Sé àwọn nà ńlo

ìgbadgbò wọn?"

Sé ó wá rí, o kò ní àsẹ tẹmí lórí ẹlòmírán. O le se isẹ́ ìránsẹ́ fún wọn, sùgbọ́n àwọn na ní láti lo ìgbàgbọ́ won. Ohun kan tí mo ma ńsọ fún àwọn ènìyàn láti se tí mo bá ńgbàdúrà fún wọn ni pé kí wọn yí àwòrán padà. Mo ńsọ̀rọ̀ nípa àwòrán tí wọ́n ti ńrí tẹ̀lẹ̀ nípa ipò tí wọ́n wà nínú ọkàn wọn. Mo fẹ́ yí àwòrán ikú nà sí ti ìyè̀.

> *À̀wọn ọmọ-ẹ̀yìn Johanu sì sọ gbogbo nǹkan wọ̀nyí fún un. [1]Nígbà tí Johanu sì pe àwọn méjì nínú àwọn ọmọ-ẹ̀yìn rẹ̀, ó rán wọn sọ́dọ̀ Olúwa, wí pé, "ìwọ ni ẹni tí ń bọ̀, tàbí kí a máa retí ẹlòmíràn?"*
>
> *Nígbà tí àwọn ọkùnrin náà sì dé ọ̀dọ̀ rẹ̀, wọ́n wí pé, "Johanu onítẹ̀bọmi rán wa sọ́dọ̀ rẹ, pé, 'Ìwọ ni ẹni tí ń bọ̀, tàbí kí a máa retí ẹlòmíràn?'"*
>
> *Ní wákàtí náà, ó sì ṣe ìmúláradá ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn nínú àìsàn, àti ààrùn, àti ẹ̀mí búburú; ó sì fi ìríran fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn afọ́jú. Jesu sì dáhùn ó wí fún wọn pé, "Ẹ padà lọ, ẹ ròyìn nǹkan tí ẹ̀yin rí, tí ẹ̀yin sì gbọ́ fún Johanu: àwọn afọ́jú ń ríran, àwọn amúnkùn ún rìn, a sọ àwọn adẹ́tẹ̀ di mímọ́, àwọn adití ń gbọ́rọ̀, a ń jí àwọn òkú dìde, àti fún àwọn òtòṣì ni à ń wàásù ìhìnrere.*
>
> —Lúkù 7:18-22

Kíyèsí Jésù kò tọ́kasí Ìwé Mímọ́ kankan, níse ni kò bá sọ pé, "Ẹ padà lọ sọ fún Jòhánù pé Ìwé Mímó yí tàbí tọ̀hún." Sùgbọ́n rárá, Ó sọ fún wọn pé ẹ padad lọ So fún Jòhànnù nípa àwọn ohun rere tí ó sẹlè nípa agbára àti àsẹ ti Ìjọba Ọlọ́run.

Lati ran ọ̀rẹ́ tàbí àwọn àbátan rẹ lọwọ́ ìwọ nà o se ohunkanna. Sọ fún ọ̀rẹ́ rẹ tí ara rẹ̀ kòdá ìtàn bí Jésù ti se mú ẹnìkan láradá. Tí ó bá séese, kí o sọ fún wọn nípa ẹnití ó ní irú àrùn yí kannà tí ó ti ńpọ́nlójú. Tí o bá fi irú àwònrán yi fún wọn yóò ru ọkàn wọn sókè àti mú ìrètí wam fún wọn. Ìrètí máa mú àwòrán dání ní, irú àwòrán yí ni ó si fẹ́ kim ọ̀rẹ́ tàbí ìbamtan rẹ má rí, tí ó lé wò wọ́n sàn kúrò nínú àrùn wọn.

Tí ọ̀rẹ́ tàbí ẹbim rẹ bá ti rí irú àwòrán yí pé ó séese fún wọn láti gba ìwòsàn, wọn yóò wa bí ọ lérè pé báwo ni yóò ti séese. Àsìkò na wá nìyì tí

ó ti ńdúro de—wọ́n yoò wá sí ọkàn wọn láti gba ìtọ́nisọ́nà ní ti ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti ìlànà òfin ti ìjọba. Wà sí fẹ́ mú wọn wá sínú ìjọba, tí wọn kò bá ti di àtúnbí lákọ̀kọ̀ àti ẹlẹ́kejì, lo àsìkò pẹ̀lú wọn láti sàlàyé Ìwé Mímọ́ fún wọn tó ní se pẹ̀lú ìwòsàn. Tí o bá séese, fún wọn ní àwọn ohun èlò tí o le sàtìlẹ́yìn fún ohun tí ó ti sọ fún wọn. Àti rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn tí wọ́n ti wòsàn kúrò nínù onírúrú àìsàn wọn tí wọ́n sì gbà ìdándè nípa síse nkan wọ̀nyíi. Nkan míràn tí mo tún má ńsé, kín tó gbàdúrà fún wọn, ní láti bi wọn lérè ni pé kílódé tí wọn fi lérò pé àwọn yóò gbàdùn bí a bá gbàdúrà. Mo fẹ́ kí ìgbágbọ wọn rọ̀ mọ ìwé Mímọ́, kì ńse pé nítorí tí a gbàdúrà nìkan.

A mọ ohun tí ìgbàgbọ jẹ́—àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run, ni *p*ẹ̀lú ìdánilójú kíkún ohun tí Ọlọ́run sọ. A sì tún ti ní òye pé ìgbàgbọ́ sí nílò láti fún Ọlọ́run ní sàkání –agbára lórí ilẹ̀ ayé nípasẹ̀ ènìyàn tí ó ní àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run

**Báwo ni a ti se ní ìgbàgbọ́**?

*Ǹjẹ́ nípa gbígbọ́ ni ìgbàgbọ́ ti í wá, àti gbígbọ́ nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.*

—Rómu 10:17

Báwo ni ìgbàgbọ ti se ńwá nimpa gbígbọ́ Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run? Kinm ni ìlànà? Gbígbọ́ Ọ̀rọ̀ níkan ni ó mú kí ìgbàgbọ́ má dàgbàsóke nínú ẹ̀mí ènìyàn?

Láti ní òye bí ìgbàgbọ́ ti se ńwá àti ohun tí Rómù 10:17 sì ńsọ nípa rẹ̀, a le wo ìwé Mákù orí kẹrin. Mo má fi ìgbà gbogbo sọ pé tí ò bá ju Bíbélì rẹ sóke sínú afẹ́fẹ, Mákù ori kẹrin ní yóò sì silẹ̀ bí ó bá délẹ̀ tán; bí ò ti se pàtàkì tó nì yìí.

Jésù ṣọ nínú Mákù 4:13 pé tí ẹ̀kọ́ tí ó ńkọ́ nínú òwe yi kò bá yé ọ, ó jẹ́ pé o kò ní ní le mọ àwọn òwe *míràn* nínú Bibélì. Mà fé sọ pé ó se pàtàkì! Kín ni ìdí tí ìpín yi fi se Pàtàkì? Nítorí ó sọ bí ọ̀run pẹ̀lú ayé ti wọnú ara wọn, bí ó ti rí sàkání-agbára gbà, àti ibi tí ó ti ńwáyé. Kò tún sí ohun tí ó tún se Pàtàkì sí ayé rẹ ju kí o mọ gbogbo ohun tí ìpín yí nsọ nípa rẹ̀ lọ.

Nínú ìpín yìí, Jésu sọ àwọn òwe mẹ̀tà fún wa tí ó níse bí ìgbàgbọ́ ti se ńse nínú ẹ̀mí ènìyàn, tí ńse bí ó ti se mọ̀ nísisiyí, àwọn ohun tí ó yẹ fún ọ̀run láti le wá jagun lórílẹ̀ Ayé. Àwọn ìtàn mẹ̀tẹ̀ta inú idpín yi ni òwe

afúnrúgbìn, òwe nípa ìdàgbà irúgbìn, òwe nípa wóró mústárdì,

Ẹ jẹ́ kí a bèrè látorí ìtàn kejì tí Jésu sọ nínum Mákù 4, ìtàn nípa ìdàgbà irúgbìn.

> *Ó sì tún sọ èyí pé, "Èyí ni a lè fi ìjọba Ọlọ́run wé. Ọkùnrin kan ń fúnrúgbìn sí ilẹ̀. Lóru àti ní ọ̀sán, bóyá ó sùn tàbí ó dìde, irúgbìn náà hu jáde, ó sì dàgbà, òun kò sì mọ̀ bí ó ti ṣẹlẹ̀. Nítorí tí ilẹ̀ kọ́kọ́ hù èso jáde fún ara rẹ̀, ó mú èéhù ewé jáde, èyí tí ó tẹ̀lé e ní orí ọkà, ní ìparí, ọkà náà gbó. Nígbà tí èso bá gbó tán, lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, òun a tẹ dòjé bọ inú ọkà náà, ó sì kórè rẹ̀.*
>
> —Mákù 4:26-29

Ohun àkókò tí a ní láti se ní kí á mọ ńtafẹ́. Kínni *irúgbìn* Jésù nmsọ̀rọ̀ nipa, kínni ilẹ̀? Bẹ́ni Jésù sàlàyé àwọn nkan méjéjì yí nínú àwọn òwe tó sáajú tí se òwe afúnrumgbìn nínú ìpín yi kannà.

Irúgbìn ní Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, a sì sọ fún wa pé ilẹ̀ ni ọkàn ọmọ ènìyàn, tàbí ẹ̀mí ènìyadn. Toríbẹ, nínú òwe yí, Jésù sọ pé ènìyàn ńfúnrúgbìn Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sínu ọkàn rẹ̀. Nígbàna, gbogbo rẹ̀ n*ípa ara rẹ*, ilẹ̀, tàbí *ọkàn* ènìyàn, bẹ̀rẹ̀ sí pèsè ìgbàgbọ́ tàbí àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run. Ìlànà tara nì yí àti bí ẹ̀mí ènìyàn rẹ̀ ti se ńsisẹ́—ohun tí ò fi sínú rẹ yóò bẹ̀rẹ̀ sí ní máa dàgbà.

Kín tó tún tẹ̀síwájú, ó se kókó kí o rántí ohun tí ìgbàgbọ́ túmò sí—*ọkàn ọkùnrin tàbí ti obìnrin Pẹ̀lú ìdánilójú kíkún ohun tí ọ̀run sọ*.

Nkan tí ó yẹ kí o rántí ńibiyí ní àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run kì íse ohunkanna pẹ̀lú Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí ó gbà sí ọkàn rẹ. Bíbélì sọ pé Ábráhámù *pẹ̀lú ìdánilójú kíkún*. Kí o le mọ ohun tí pẹ̀lú ìdánilójú kíkún jẹ́ tàbí bí ó se rí; kání mo ní kí o bẹ́ sílẹ̀ láti orí Empire State Building ni New York City. Kí o bá le gbìyànjú rẹ̀, mo wá sọ fún ọ pé tí o bá le di apá rẹ mú le dádá tóo, o le fò sílẹ̀ láìfarapa. Wa̍rọ ra rẹrín nítorí tí ó MỌ ohun tí ó le sẹ́lẹ̀ sí ọ. Nítorí pẹ̀lú ìdánilójú kíkún ni ti èsì rẹ̀. Nkan tí pẹ̀lú ìdánilójú kíkún jẹ́ nìyí. O *mọ̀,* oní ìdánilójú kíkún, kò sí àwọn nkan míràn pé ó seése—pé wà kú tí o báfò.

Jẹkí á tún lọ wo ipò míràn àti rí bí o ti máa se pẹ̀lú rẹ. Jẹ́ kí á wo wípé o ní ìsù ọ̀mọ̀/ kókó kan tí ó tóbi tí ó sì se rí ní àgọ́ ara rẹ, tí dókítà sọ pé osù kan péré ni ó kù fún ọ láyé. O ní àrùn jẹjẹrẹ. Kódà, Dọ́kítà sọ pé irú ẹ̀yà àrùn jẹjẹrẹ tí o mú ọ tún yàtọ̀ pé kò sí ẹnìkan tí ó ní irú rẹ̀ tóyè.

Báyìí, jẹ́ kí á wá wòó pé o mọ ohun tí 1Peteru 2: 24 sọ.

*Ẹni tí òun tìkára rẹ̀ fi ara rẹ̀ ru ẹ̀ṣẹ̀ wa lórí igi àgbélébùú, pé kí àwa lè di òkú sí ẹ̀ṣẹ̀, ki a sì di ààyè sí òdodo: nípa ìjìyà ẹni tí ó mú yín láradá.*

—1Pétérù 2: 24

Ìwé Mímọ sọ ìdáhùn fún wa, sùgbọ́n ìwọ àti èmi ni ìsòro kan: Nínú ìjọba òkùnkùn ni a ti dàgbà, ẹ̀tàn àti ikú yí gbogbo waká. A dàgbà nínú ìjọba tí ìbẹ̀rù a`si ti ní ìdánílójú kíkún ohun ti ìbẹ̀rù sọ. Torínà, nínú àpèjúwe tó wà lókè, a ti kọ́ wa pé àrùn jẹjẹrẹ le pàyàn. A sì ní ẹ̀rí láti inú gbogbo àwọn ilé isẹ́ agbéròyìnjáde pé òtítọ ni. Báwo wá ni ati se fẹ́ yí àdéhùn wa padè? Báwo ni a ti se fẹ́ pẹ̀lú ìdánilójú kíkún ohun tí Ọlọ́run sọ? Ó da, nítòótọ́, a kò le dá a se fúnra wa. Sùgbọ́n Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run wà láyè ó sì kún fún agbára, àti nípa bí o ti se ńgbin sínú ẹ̀mí rẹ, gbogbo rẹ̀ fúnrarẹ̀, ẹ̀mi rẹ àti Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yóò sì bẹ̀rẹ̀ sí ní mú àdéhùn wá pẹ̀lú ohnu tí ọrun sọ.

*Ó sì tún sọ èyí pé, "Èyí ni a lè fi ìjọba Ọlọ́run wé. Ọkùnrin kan ń fúnrúgbìn sí ilẹ̀. Lóru àti ní ọsán, bóyá ó sùn tàbí ó dìde, irúgbìn náà hu jáde, ó sì dàgbà, òun kò sì mọ̀ bí ó ti ṣẹlẹ̀.* ***<u>Nítorí tí ilẹ̀ kọ́kọ́ hù èso jáde fún ara rẹ̀, ó mú èéhù ewé jáde</u>****, èyí tí ó tẹ̀lé e ní orí ọkà, ní ìparí, ọkà náà gbó. Nígbà tí èso bá gbó tán, lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, òun a tẹ dòjé bọ inú ọkà náà, ó sì kórè rẹ̀."*

—Mákù 4:26-29

Gbogbo rẹ̀ fún ara rẹ̀, ilẹ, (ọkàn rẹ) ó mú àdéhún jáde. Kíyèsi o kò le gbàdúrá fún ìgbàgbò; ìse ọkàn rẹ̀ àti ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ni. Bí a ti fẹ́ lọ wo àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí, a le rí pé àdéhùn ọkàn wa àti ọ̀run ńsisẹ́ lọ. Kò kí sẹlẹ̀ bẹ lẹ́kanna. Àpèjúwe tí wọ́n sọ fún wa,lákọ́kọ́, nígbàtí ọkàn wa bá ti gba ọ̀rọ̀ náà, ìgbàgbọ́ yó bẹ̀rẹ̀ sí ní dàgbà bí àsẹ̀sẹ̀yọ irúgbìn tí ó hu ewé jáde. Yóò sì maa hù lọ títí yó fi dàgbà *èyí tí ó tẹ̀lé e ní orí ọkà*. Orí rẹ̀ ni àwọn èso yóò sì wà. Ní àsìkò yí tí igi sẹ̀sẹ̀ ńdàgbà kò ní tì sí èso tí o le ríjẹ́ lórí rẹ̀. nítorití kò tí gbo, àwọn èso rẹ̀ kò ti pọ́n, síbẹ̀ o si ńdàgbà lọ.

Torinà bẹ́ẹ̀ni Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run rí. Kò tí sí ìyípadà kan tí ó tì hàn nínú ara nígbà tí ìgbàgbọ́ rẹ sí ńdàgbà. Kò tí sí àdéhùn síbẹ̀, sùgbọ́n ó dájú pé èwéko sí ńdàgbà, a ńpèsè ìgbàgbọ́, àti àdéhùn na sí ńwáyé. Jésù tún tẹ̀síwájú láti sàlàyé pé tí èso tí ó wà lórí igi bá ti gbó dádá, tí ó ti pọ́n, àsìkò ìkórè titó, àdéhùn tí wà níbẹ̀, àti pé níbáyí ìgbàgbọ ti wà níbẹ̀.

Nígbàtí ó bá gbin irúgbìn sínú ilẹ̀, nípasẹ̀ ìlànà híhù jáde, tí ohun ọ̀gbìn nà síbẹ̀rẹ̀ sí ní dàgbà, sùgbọn tí kò sì tí sí èso kankan ní orí rẹ̀. irúgbìn na yóò sì ma dàgbà lọ níwọ̀n ìgbà tí o ti wà ní agbègbè tó dára. Bí o sì ti ńdàgbà, yóò má yọ èso rẹ̀ jáde.

Ẹ jẹ́ kí á sọ pé ogbin àgbàdo. Àgbàdo na ti bẹ̀rẹ̀ sí ní yọtí jáde, ní àkókò, díẹ̀ ní yóò kọ́ yọ jádè tí kò sí ní tí gbó láti jẹ. Sùgbọ́n tí o báyá, àgbàdò na yóò gbó láti já. Jẹkí o ye ọ. Ní àsìkò tí àgbàdò tí ó tì hù jáde ti bá èyí tí a gbìn sínú ilẹ̀ mu àdéhùn ti yá.

**Nígbàtí irúgbìn tí ó so lórí ohun tí a gbìn bá ti gbó, yóò dàbí èso tí a gbìn <u>GANGAN</u>.**

Gbin èso àgbàdo, tí o bá ti gbó yóò jáde bí èso tí o gbìn ná ni. Ọ̀kanna ní wọ́n. Wọ́n rí bákanna, bákanna ni wọ́n rí lẹ́nu tí o kò sì ní le sọ ìyàtọ̀ láàrin wọn.

Jẹ́kí tún ohun tí Jésù nsọ sọ. Nígbàtí a bá ti gbọ Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. (Romu10:17), a ńfọ́n Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ká sínú ẹ̀mí ènìyàn, ọkàn wa. Tí a bá wá pa ọ̀rọ̀ ná mọ́ nínú ọkan wa. Yóò wá máa dàgbà títí yóo fi gbó, ọkàn wa yó wà pẹ̀lú ìdánilójú kíkún ohun tí ọ̀run sọ. Ọ̀run àti ayé yóò wà bá ara wọn mu, ọ̀run wá ti gba sàkání lábẹ́ òfin lórí ilẹ̀ nípasẹ̀ ẹni tí ó ní ìdánilójú kíkún. Èrò àti ìgbàgbọ́ wa ti báramú, ohun tí ọ̀run sọ pẹ̀lú ìdánilomjú kíkumn. Èyí kì se tí ọgbọ́n orí. Èyim tí di ohun gan tí a gbàgbọ́ gẹ́gẹ́ bí a tí ní ìdánilójú pé àpáta yò jábọ́sílẹ̀. Ọ̀run fúnrumgbidn Ọ̀rọ̀ láti ọ̀run sínú ayé níbití yóò ti mu àdéhuǹ wá àti ìfẹ́ Ọlọ́run. Tí ọrun bá sọ pé a ti mú ọ láradá, nígbàtí ọ̀rọ̀ na bá ti dàgbà nínú ọkàn rẹ, ohun gbogbo tí wà máa rí ni ohun ti ọ̀run sọ. Kò ní sí ẹ̀rù mọ́, Nígbàtí o bá pa ojú rẹ dé, o má rí ara rẹ pé ati wò ọ sàn!. Idí sì nìyí tí Hébérù 11:1 KJV fi sọ pé,

*Ǹjẹ́ ìgbàgbọ́ ní ìdánilójú ohun tí o ń retí, <u>ìjẹ́rìí ohun tí a kò rí</u>.*

O lé má ti fi ojú rí nígbangba, sùgbọ́n o ti ri nínu ẹ̀mị rẹ; o sì dàbí bí ẹnipé o mú lọ́wọ́ ni. Èyí sì ni àdéhùn tí à pè ní ìgbàgbọ́, àti ìgbàgbọ́ yi ni

yóo mú àwòrán nà wá láti kọjá rẹ̀ ní ìpele yí nínú ayé rẹ!

Sùgbọ́n kì ise ibití Mákù 4 dúró sí nìyìí. Lẹ́yìn tí ó ti kọ́ wa ní bí ọkàn wa ti se le wà ní àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run tí ìgbàgbọ̀ wa sì wà níbẹ̀ ó fún wa ní ìtọ́sọ́nà lórí, báwo ni a ti le kórè àwọn èso na.

> *Nígbà tí èso bá gbó tán, **lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, òun a tẹ dòjé bọ inú ọkà náà**, ó sì kórè rẹ̀.*
>
> —Mákù 4:29

Kíyèsi pé bíotilẹ̀jẹ́wípé ọkàn wa nínum àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run ìgbàgbọ́ sí wa, kò sí ohun kankan tí ó tì sẹlẹ̀. Kín ni ìdí? Gẹ́gẹ́ bí mo ti máa ńsọ nígbà gbogbo, o ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin sàkání-agbára lórí lẹ̀ ayé.

Njẹ́ o rántí ohun tí a jíròrò nípa ìwé Lúkù orí kẹjọ tí óníse pẹ̀lú obìnrin onísun ẹ̀jẹ̀? Rántí, Jésù sọ pé "Ọmọbìnrin ìgbàgbọ́ *rẹ* mú ọ láradá." Mo sì sọ fún ọ nígbàna nígbàtí Jésù lo ọ̀rọ̀ yìí "ọmọbìnrin" Ó ńtọ́kasí ẹ̀tọ́ tó ní níwájú ọ̀run. Ọmọbìnrin Ábráhámù ní se. Ó ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin. Mo fi wé kí ó ní okùn iná tí ó ti so mọ́ ilé rẹ. Iná ti wà níbẹ̀, sùgbón o ní láti tan iná kí ó le rí ìmọ́lẹ̀. Ní ọ̀nà yí kanna, ní gbàtí o bá ti fẹsẹ̀ ìgbàgbọ́ múlẹ̀, agbára na ti wà, sùgbọ́n kòsim ǹkan tí yóò sẹlẹ̀ tító wà fi tẹ̀ẹ́ kótàn.

ÌWỌ ní láti sọ agbára ti Ìjọba Ọlọ́run kalẹ̀ lórí ilẹ̀ ayé, nítorí iwọ nìkan ni, ọkùnrin tàbí obìnrin lórí ilẹ̀ ayé, tí ó le seé lábẹ́ òfin. Ìlànà òfin yí gan ni bí o ti se dẹni ìgbàlà bí ìwe Rómù 10:10 ti sọ.

> *Nítorí ọkàn ni a fi ìgbàgbọ́ sí òdodo; ẹnu ni a sì ń fi ìjẹ́wọ́ sí ìgbàlà.*
>
> —Rómù 10:10

Nítorí pẹ̀lú ọkàn, ní ènìyàn fi gba Ọ̀rọ̀ gbọ́ sí òdodo. Òdodo jẹ ẹ̀tọ́ lábẹ òfin tí ó túmọ̀ sí sísàkíso òfin. Toríbẹ̀, nígbàtí ọkàn ọkùnrin tàbí obìnrin wà ní àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run—nígbàtí wọ́n bá gba ohun tí ọ̀run sọ gbọ́—wọn di òdodo níwájú ọ̀run òn Ayé. Ó wá ti di ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin fún ọ̀run láti sàn *wọnú* ayé wọn àti *ńipasẹ̀* ayé wọn àti ní ipa lórí ayé nítorí ti Ìjọba Ọlọ́run. Sùgbọ́n ó sàjèjì, kódà bí o ti se wá jẹ́ ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin to tí wọn sì wà nínú ìgbàgbọ́, síbẹ̀ kò sí ohun tí ó sẹlẹ̀. Sudgbọn Garry, mo lérò pé ohun tí o sọ nipé tí mo bá ní ìgbàgbọ́, ó ti fún ọ̀run ní ẹ̀tọ́ agbára níbíyí" ò tọ́ ni,

sùgbọ́n ẹni na ní láti lo àsẹ ọ̀run nà níwọ̀n ìgbà tí ìgbàgbọ́ ti wà. Ẹ jẹ́ kí á wo ẹsẹ̀ iwé Mímọ́ yi lẹ́ẹ̀kanasi.

> *Nítorí ọkàn ni a fi ìgbàgbọ́ sí òdodo;* **ati pe pelu ẹnu re ni a sì ń fi ìjẹ́wọ́ igbagbo re sí ìgbàlà**.
>
> —Rómù 10:10

**NÍWỌ̀N ÌGBÀTÍ O BÁ WÀ NÍNÚ ÌGBÀGBỌ́, TÀBÍ ÒDODO, Ó TI WÁ DI ÒFIN FÚN ỌRUN LÁTI WÁ JAGUN NÍ AYÉ.**

Níkété tí o bá ti wà nínú ìgbàgbọ́ tàbí òdodo, o ti wà di òfin fún ọ̀run láti wá jagun ní Ayé. Sùgbọ́n kíyèsi pé ó wá sọ pé pẹ̀lú *ẹnu rẹ* ni wà sì fi jẹ́wọ́ sí nígbàlà. Sé o ti rí ipa méjéjì? Ipa ti ọrun mú Ọ̀rọ̀ wá sínú ọkàn rẹ níbití yó ti má hu àdéhùn lórí ilẹ̀ ayé níbiyí. Nígbàtí, àdéhùn bá ti wà, tàbí ìgbàgbọ, níbẹ̀ ni ìwọ gan yóo ti gbé ìgbésẹ̀ lórí àdéhùn wà si sọ̀rọ̀ àsẹ ti ọ̀run jáde si ipò na kí o sì le gba ohun ti ọ̀run sọ.

Nínú Bíbélì wa tí a ńkà Mákù 4, ó sọ pé. Nígbàtí èso bá gbó tán, ènìyàn (lórí ilẹ̀ ayé) á tẹ dòjé bọ inú ọkà náà. Òun ni ó gbọdọ̀ fi ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sínú ìse níwọ̀n ìgbà tí ó ni ìgbàgbọ́ tí ò sí tí ko ìkórè.

Jẹ́kí npadà lọ sọ̀rọ̀ lórí dòjé tí a ńsọ nínú Mákù 4 fún ìgbà dịẹ. Mo gbàgbọ́ pé ọ̀pọ̀ àwọn ìjọ ní ayé ní wọn kò ti kọ́ nípa bí a ti se ńlo dòjé, tí ó túmọ̀ sí pé wọn ò ti kọ ẹ̀kọ́ bí wọn ti ńko èrè nkan tí wọ́n nílò. Èmi na kò mọ tẹ́lẹ̀ títí di ìgbàtí Ọlọ́run bẹ̀rẹ̀ sí ní kọ mi bí Ìjọba ọ̀run ti se ńsisẹ́. Ìfihàn àkọ́kọ́ tí mo ní nípa ìlànà nínú Ìjọba wáyé ní bí ọdún díẹ̀ sẹ́yìn nígbàtí wọn fiwé pè mí láti wá bá wọn sọ̀rọ̀ nínú ìsìn alẹ́ ọjọrú kan ńinú ìjọ kan ní Allanta.

Ìjọ na kò fi bẹ tóbi, sùgbọ́n ó dára bẹ fún mi. Mo kàn fẹ́ràn láti má kọ́ àwọn ènìyàn nípa Ìjọba. Bí mo ti dé ìjọ nà, ó jẹ́ ohun àjèjì sí mi pé ilé ìjọsìn na wà ní títì kò sì sí ẹnikankan níbẹ̀. Nkan bí ìsẹ́jú mẹwa lókù sí àkòkò tí ìsìn yẹ kò bẹ̀rẹ̀.

Mo wa gbó ariwo ọkọ̀-akẹ́rù kan ní ẹ̀yìn mi, mo wòó ó di ọkọ̀ kan tí ó ti gbó tí wọ́n ńfà jáde lẹ́yìn ilé ìjọ́sìn na. Èmi kò ro nkan nípa rẹ̀. Nígbàtí ó jẹ́ pé ilú Atlanta ní mo gbé.

Bí mó tí se dúró ni arákùnrin kan tọ̀ mí wá láti ẹ̀yìn ilé nà ó sì júwe ara rẹ̀ fún mi bí pásítọ̀ ìjọ na. Ó ní kín má bínú nítorí tí òun pẹ́ dé, nítorí ọkọ̀-akẹ́rù rẹ̀ kò tètè sisẹ́ ni. Ó ní òun ní láti máa tìí da fírìì sí ìsàlẹ̀ kí ó tó le sisẹ́ pé nígbàmíràn kò tí lẹ̀ ní sisẹ́ rárá, òun yóò wá ní láti rin ìrìn ṁailì márun wá sí ilé ìjọ́sìn.

Mo ní láti gbà pé nkan tí ó ńsọ yí jọmílójú. Ó tẹ̀síwájú láti má sàlàyé pé isẹ́ ìránsẹ́ oun gan ni kí òun má jáde lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn ènìyàn tí òun sì npèsè oúnjẹ bí ẹgbàárún ní osù láti ibi tí òun wà.

Bí pásítọ̀ na ti ńsọ̀rọ̀ ni inú fẹ́ má bími. Ìránsẹ́ Ọlọ́run kan nìyí tí ó ńbọ́ ẹgbàárun àwọn ènìyàn ní ososù tí kò sì ní mọ́tò tí ó gbádùn láti wà? Mo le ba yanjú ìyẹn. Mo ní mọ́tò kan tí o sì tuntun díẹ̀ nílé pẹ̀lú ọ̀kẹ́ kan máili lórí rẹ̀ ní ilé tí mo le fún un.

Mo sì sọ èrò mí fún mà ràn ọ̀kan lára àwọn òsìsẹ́ mi lọ sí Atlanta pẹ̀lú mọtò na. Lóòtọ́ inú rẹ̀ dùn. Mo lo alẹ́ ọjọ́ nà láti kọ́ ọ àti ìjọ rẹ̀ kékeré nípa Ìjoba Ọlọ́run àti bí ó ti se ńsisẹ́ ni ohun tí ó jẹ́ mọ́ owó. Mo mọ̀ pé nkan tó se pàtàkì ni ti wọn bẹ̀rẹ̀ sí ni se àfihàn ohun tí Ìjọba jọ fún àwọn tí wọ́n nílò rẹ ní kíákiá.

Nígbatí mo dé ilé, mó sètò fún ọkọ̀ náà kí wọ́n wá gbé lọ sí Atlanta. Nígbàti ọkan nínú àwọn òsìsẹ mí wá láti gbé ọkò na. Mo mọ̀ pé mò ńsowò tẹ̀mí nínú ọ̀run ni. Mo mọ pé bí mo ti se fi ọkò na sílẹ̀ sínu Ìjọba Ọlọ́run, Mo le gba Ọlọ́run gbọ́ fún ọkọ̀ tí èmi na nílò bákanna.

Èmi kì íse ẹniti ó fi bẹ́ẹ̀ fẹ́ràn ọkọ̀, tí ò túmò sí pé èmi kì ra ọpọ̀ ọkọ̀. Àwọn kan má se bẹ, sùgbọ́n kì íse èmi. Torínà, mo gbé owó mi le orí ọkọ̀ na bí òsìsẹ́ mi ti wá gbé e, mo wá sọ báyi pé, Bàbá, mo fi ọkọ̀ yí sínú isẹ́ rẹ ni Atlanta. Bí mo ti fi ọkọ̀ yí sílẹ̀, mo fúnrúgbín rẹ̀ bí irúgbìn mo sì gbàgbọ́ pé mam rígbà…" Mi ò le ronú irú ọkọ̀ tí mo fẹ gan, mo ní ma padà wá lórí rẹ̀!"

Ó da, lẹ́yìn bí osù melo sí ìgbàna, èmi ò tilẹ̀ ronú púpọ̀ nípa ọkọ̀, sùgbón ní òwúrò ọjọ́ kan mo bi Drenda pé irú ọkọ̀ wo ni o wùú láti ní. Lẹ́yìn ìgbàtí ó ronú fún ìgbà díẹ̀, ó ní ọkọ̀ alàyípadà (kọnfátíbù) na dára. Mo ní irú èwo gan ni ó fé, kò sí ẹnikan nínú wa tí ó mọ irú èyítí ó wà lóde. Ní wọ̀n ìgbàtí mo ti fẹ́ láti ra ọkọ̀ fún Drenda, mo fẹ kí ó sọ́ irú èyí tí ó fẹ gan, mó wá sọ fún kí ó lọ wo lórí ìtàkùn ayélujára tàbí kí o wo àyíká kí ó sì jẹ́ kín mọ̀ tí ó bá ti rí èyíti ó fé. Bẹsìni, a kò sọ fún ẹnikankan nípa èrò ọkàn

wa láti ra ọkọ̀ titun, Sùgbọ́n a wá ọkọ̀ tí a fẹ́ bí a tí ńjáde kákiri.

Ní ọjọ́ kan a ńlọ sí ilé ìta óunjẹ kan láti jẹ óunjẹ ọ̀sán, lójiji Drenda pariwo pé, "irú rẹ̀ nìyí!"

"Se ohun na nìyí?" Mo bèrè.

" Ọkọ̀ tí mo fẹràn." Ó nawọ́ sí ibití wọ́n gbé ọkọ̀ na sí. Mo wá wa ọkọ̀ yí ibití àwọn ọkọ̀ ná wà ká mo sì ri tí ó wà lẹyìn rẹ̀ BMW 6 series Ci kọnfátíbù, ọkọ̀ na dára nítòótọ́. Ó sì ma jẹ́ ọkọ̀ tí owó rẹ̀ pọ̀ bákanna. Mo kí pé ó mọ ohnu tódára mo sì tún sọ fún pé ọkò na dára ó sì rewà.

Níbáyìí, ó ní láti mọ̀ pé àti èmi àti Drenda a kò jáde lọ láti lọ san owó tí ó pọ̀ fún mọ́tò na. Bí mo ti sọ, èmi kì íse ẹnití ó máa ra mọ́tò jọ. Nítorí o ní ètò ìsùná ni mo jẹ́, mo sìtún mọ̀ pé kíákíá ni owó orí wọn máa dínkù, ìdí tí ó fi yẹ kí ènìyàn ra ọkọ̀ tí kò tí ju ọdún kan sí méjì lọ tí ó jáde. Èròngbà mi nìyí, láti wá èyí tí ó dára kan láti rà.

Ní bí ọ̀sẹ̀ kan sí ìgbàna, arákùnrin kan láti inú ìjọ pè mí ó ní , mo ti rí mọ́tò Drenda!" Mo kọ́ dákẹ nítorí a kò sọ fún ẹnìkẹni nípa BMW tí a rí ní ọ̀san ọjọ́ nà.

Mo wá bií léèrè pé irú mọ́tò wo ni, ó ni BMW 6 series Ci konfatibu. Ó ní bí òun ti ńwa ọkọ̀ kiri ní òun bá rí i, Olúwa wá sọ fún pé mọto Drenda nìyí.

Ó da, sé òn tẹ́tísílẹ̀ sí mi," Mo sọ fún. Ọkọ̀ na kò ti ju bí ọdún kan to jáde lọ ó sì tuntun àti pé ó sì wà ní ipò tódara. Mo parí ọ̀rọ̀ mi pẹ̀lú pé mo sì ti san owó fún mọ́tò na. Drenda gba mọ́tò re. Báwo ni om ti se sẹlẹ̀.? Ẹ jẹ́ kí á fi ìtàn yí wé ńkan tí a ti kọ́ nípa wíwà nínú ìgbàgbọ́ àti kí o tẹ dòjé bọ.

Nígbàtí tí mo gbé mọ́tò mi silẹ̀, mo wà nínú ìgbàgbọ́. Sùgbọ́n nígbàtí Drenda pariwo rẹ̀ síta," òhun gan ni!" Òun fi dòjé bọ inú rẹ̀, lẹ́yìn bí ọjọ́ malo mọ́tò na yọjú.

Bí ó tilẹ̀jẹ́wípé mo gbọ́ tí ó ńpariwo rẹ̀, Òhun ni! Èmi ko ti lẹ̀ro ohun tí Mákù ori kẹrin àti dòje sọ. Sùgbọ́n ìtàn yí jẹ kí ó hàn kedere.

Mo ti sọ bí ìgbà díẹ̀ pé mo ní saarè ilẹ̀ ọgọ́ta. Bí saare ilẹ̀ mẹ́wa nínú rẹ̀ jẹ́ irà. Mo fẹ́ràn láti má sọdẹ nínú òjò, bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé nígbàtí mo wà ní giramma ní mo ti sọdẹ pẹ́pẹ́yẹ sẹ́yìn, mi ò ti sọdẹ pẹ́pẹ́yẹ ní Òhíò níbíyìí. Níbí ọdúnkan inú irà yí kún fún omi, àwọn pẹ́pẹ́yẹ kan bẹ̀rẹ̀ sí ní fò wá sí bẹ̀ nị ti agbo wọn sìpọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn ní wọn máa ńfò wá ní alalẹ́. Ní alẹ

ọjọ́kan mo gbé ìbọn mí mo sì jáde lọ láti lọ pa díẹ̀ lára àwọn pẹ́pẹ́ye láti jẹ lálé. Èmi àti àwọn ọmọkùnrin sì gbádùn bí ati dọde àwọn pẹ́pẹ́ye díẹ.

Ohun kan tí mo sàkíyèsí, nígbàna, nipé ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àwọn pẹ́pẹ́yẹ ná má ńwà ní deédé ibití mo ti le yin ìbọn mi. Nígbàti ó bá fẹ́ pa pẹ́pẹ́yẹ, òfin gbà ọ́ láyè láti lo ìbọn onírin bí ó ti lòdì sí sakabùlà. Nítorí ìbọn sakabùlà sì wúwo ó sì máa lọ sí ọ̀nà jínjìn ju ìbọn onírin lọ, wàhála tí ó má wà pẹ̀lú ìbọn yínyìn láti ọ̀nà tójínnà nígbàti ó bá fẹ́ sọdẹ pẹ́pẹ́yẹ nìyìí. Sùgbọ́n ní àsìkò yí, bí mo ti ńbá àwọn díe tí àwọn ná sọdẹ pẹ́pẹ́yẹ sọ̀rọ̀, wọ́n wa sọ fún mi nípa ìbọn tuntun kan tí wọ́n se fún pípa pẹpẹ́yẹ nìkan. Àwọn le yin ìbọn tí ó wúwo wọn sì wọ kámofílagì bákanna. Ó wùmí láti ra irú rẹ̀ kan, sùgbọ́n àsìkò osù Ọ̀pẹ ni tí àsìkò sísọdẹ pẹ́pẹ́yẹ ti ńtán lọ. Torí ìdì èyí mi ò tilẹ̀ ronu pípọ̀ nipa rẹ̀.

Mo wá kú dúró ní Cabela, ilé ìtajà tí a ti máa ńra ohun èlò ìdárayá wa, ní ìbẹ̀rẹ̀ ọdún nínú osù ìkínní fún àwọn nkankan, mo wá rántí àwọn ìbọn pẹ́pẹ́yẹ. Mo fẹ́ láti rí ọ̀kan. Torínà, mo kọjá lẹ́gbẹ ibití wọ́n kó ìbọn wọn sí nígbàtí mo ńjáde lọ, mo sì wá rí apákan tí ìbọn titun tí wọ́n yàsọ́tọ̀ fún sísọdẹ orí omi. Mo rántí láìronú nípa rẹ̀, mo nàka mi sí ọ̀kan tí mo lérò pé ohun ni ó dára jùlọ, mo sì pariwo síta pé, Olúwa èyí ni màárà" Mi ò tilẹ̀ ronú nípa rẹ̀ bí mo ti sọ́; ó kàn jáde ní ẹnu mi na ni. Àsìkò sísọdẹ̀ pẹ́pẹ́yẹ tún di ìgbà míràn, mi ò sì lérò láti ra ìbọn na kí ó tó di ìgbà tí ó bá súnmọ.

Ọ̀sẹ̀ méjì lẹ́yín ìgbàna, wọ́n fi ìwé pè mí láti wá bá wọn sọ̀rọ̀ ní nibi àpérò àwọn olóko-òwò kan. Bí mo ti parí ni, adarí ilé isẹ́ nà CEO jáde wá láti dúpẹ́ lọ́wọ́ mi ó sì sọ pé àwọn ní ẹ̀bùn kan fún mi. Sí ìyàlẹ́nu, ó mu irú ìbọn tí mo fẹràn gangan—*irú rẹ̀ gangan* tí mo tọ́kasí ní bí ọ̀sẹ̀ méjì sẹ́yìn ní ilé ìtajà Cabela. Lóòtọ́, ó yà mílẹ́nu gan ni bí irú ẹ̀bùn yí, Síbẹ̀ mo sì mọ pé kòsèèsì. Mo rántí ohun tí mo sọ ní ilé ìtajà Cabela mo sì mọ ohun tí mo se. mo ti tẹ dòjé bọ inú rẹ̀!

Ní òye oun tí ó sẹ̀sẹ̀ kà tán ní ìpín yìí gẹ́gẹ́ bí mo ti sọtẹ́lẹ̀, ó se pàtàkì fún ọ láti le gba ohunkóhun àti ohun gbogno láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run. Ohun gbogbo tí ó bá ti gbà láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run ni yóò gba ìlànà kan na, rí dájú pé o ní òye ohun ti ó sẹ̀sẹ̀ kàtán.  Túnkà tí o bá nílò láti se bẹ́ẹ̀! Ó se Pàtàkì!

ORÍ KẸJỌ

# O NÍLÒ ÀPAMỌ́WỌ́: APÁ KEJÌ

Aní láti gba ní ọ̀nà gígùn tí a gbàà yìí nítorí tí mo mọ̀ pé ó se pàtàkì fún ọ láti rí nkan dìmú lórí ohun tó níse nípa Ìjọba. Lẹ́ẹ̀kansi, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Krìstìánì ni kò ní òye bí ìjọba ti ńsisẹ́ lábẹ́ òfin lórí ilẹ̀ ayé, bẹ́ẹ̀sìni wọ́n kò sì ní òye ètò tí wọn ní fún ara wọn nínú Ìjọba bákanna. Sé o wá rí ìdí tí mo fi fa àkòrí lórí ìgbàgbọ́ àti sàkání-agbára gùn báyìí. Nítorí tí o kò bá ní òye tótó lórí rẹ̀ láti ìbẹ̀ẹ̀rẹ̀, ohun tí iwé mímọ́ ńsọ nínú Lúkù pé kí á tètè wá Ìjọba Ọlọ́run ná àti ohungbogbo tó kù ni a fi fún wa le má ye ọ tó.

Nísisìyí tí o ti mọ ohun tí o túmọ̀sí, ẹ jẹ́ kí á padà lọ wo ẹ̀kó nà.

> *Kí ẹ má sì ṣe lé ohun tí ẹ ó jẹ, tàbí ohun tí ẹ ó mu, kí ẹ má sì ṣe ṣe àníyàn nínú ọkàn. Nítorí gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni àwọn orílẹ̀-èdè ayé ń wá kiri: Baba yín sì mọ̀ pé, ẹ̀yin ń fẹ́ nǹkan wọ̀nyí. Ṣùgbọ́n ẹ máa wá ìjọba Ọlọ́run, gbogbo nǹkan wọ̀nyí ni a ó sì fi kún un fún yín.*
>
> *"Má bẹ̀rù, agbo kékeré; nítorí dídùn inú Baba yín ni láti fi ìjọba fún yín. Ẹ ta ohun tí ẹ̀yin ní, kí ẹ sì tọrẹ àánú kí ẹ sì pèsè àpò fún ara yín, tí kì í gbó, ìṣúra ní ọ̀run tí kì í tán, ní ibi tí olè kò lè súnmọ́, àti ibi tí kòkòrò kì í bà á jẹ́. Nítorí ní ibi tí ìṣúra yín gbé wà, níbẹ̀ ni ọkàn yín yóò gbé wà pẹ̀lú."*
>
> —Lúkù 12:29-34

Lẹ́ẹ̀kansi, Bàbá ti mọ ohun tí o nílò, àti pé ohungbogbo tí o nílò ni Baba ti pèsè sílẹ̀ tí ó sì jẹ tìrẹ, sùgbọ́n o ní láti mọ́ àti ní òye ìlànà òfin tí o fi le rígbà láti ọ̀run kí o sì le máa jẹ̀gbádùn gbogbo tí Ó ní.

Ẹsẹ̀ kejì-lé-lógbọ̀n se àlàkalẹ̀ àwọn ohun ìní aláràgbàyídá tí ó ti rígbà gẹ́gẹ́ bí ọmọ Ọba kùnrin àti obìnrin. Ó sọ pé, "***nítorí dídùn inú Baba yín ni láti fi ìjọba fún yín.***"

> *Nítorí ẹ̀mí mímọ́ ń sọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ nínú ọkàn wa, ó sì ń sọ fún wa pé, nítòótọ́, àwa jẹ́ ọmọ Ọlọ́run. Níwọ́n ìgbà tí a jẹ́ ọmọ rẹ̀, ǹjẹ́ ajogún ni àwa, ajogún Ọlọ́run, àti àjùmọ̀jogún pẹ̀lú Kristi, bí ó bá ṣe àwa jìyà, kí a sì le ṣe wá lógo pẹ̀lú rẹ̀.*
>
> —Rómù 8:16-17 (KJV)

Páùlù sọ wípé a jẹ́ àjùmọ̀jogún pẹ̀lú Krístì ní a jẹ́. Gẹ́gẹ́ bí ọmọkùnrin àti obìnrin, o ní ogún ìní, ti Ìjọba.

Dúró kí o ronú nípa ọ̀rọ̀ yí fún ìgbà díẹ̀. O ti ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin sí ohun gbogbo tí ń se ti Ìjọba. O kò nílò láti má bẹ̀bẹ̀. Tìrẹ ni gbogbo rẹ̀.

Oh, báwo ni kò bá ti wù mí kí o gba àwọn nkan tí mò ńsọ yí mú. Ìdí nìyí tí 2 Kọ́ríntì 1:20 se sọ àwọn ǹkan wọ̀nyí pé:

> *Nítorí tí gbogbo ìlérí Ọlọ́run dí "Bẹ́ẹ̀ Ni" nínú Kristi. Nítorí ìdí èyí ní a ṣe ń wí pé "Àmín" nípasẹ̀ rẹ̀ sí ògo Ọlọ́run.*
>
> —2 Kọríntì 1:20

Ìdí sìnìyí tí o fi wà nínú ìwé mi tó gbẹ̀yìn, *Yíyí Ètò Ìsúná Rẹ Padà: Agbára ti Ìpèsè*, Mo sọ fún ọ pé Àdúrà Olúwa wá bí ìbéèrè tàbí ẹ̀bẹ̀ ni ìlànà ti òfin. Kì se pé ò ńbèèrè nígbàtí o sọ pé *"Fún wa ní óunjẹ òjọ́ wa lónìí*." Kì íse ìbérè nìyí; ón bèrè ni.

Gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ fún àwọn ọmọ mi pé ẹ kò nílò láti máa bẹ mí fún oúnjẹ òwúrọ̀ yín (wọ́n nse bí ìgbàtí àwọn ni ó ni, pẹ̀lú pé "Hey, bàbá, ẹ mú ẹyin sọwọ́ sí wa."). Bí o ti wà pẹ̀lú Ìjọba na nìyí—o ní ẹ̀tọ́ sí ohunkohun tàbí gbogbo ohun tí se ti Jésù Krístì.

Yàtọ̀sí pé oní ètọ́ àti gba ohun tí Ìjọba bá ní nínú rẹ̀, bákanna o tún jẹ́ ọmọ ìlù ti Ìjọba, tí ò tún ní ọpọ̀lọpọ̀ àwọn ànfàní. Gẹ́gẹ́bí ó ti jẹ́ ọmọ onílu ní United State tí o sì ní ẹ̀to sí àwọn ànfàní ti o le má le lò tí kò bájẹ́ bẹ̀.

*Ǹjẹ́ nítorí náà ẹ̀yin kì í ṣe àlejò àti àjèjì mọ́, ṣùgbọ́n àjùmọ̀jogún ọmọ ìbílẹ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn mímọ́, àti àwọn ará ilé Ọlọ́run.*

—Efesu 2:19

Níparí, ẹ jẹ́ kí á sọ̀rọ̀ nípa àpàmọ́wọ́! Jésù sọ pé o nílò àpò, sé o rántí?

*Ẹ ta ohun tí ẹ̀yin ní, kí ẹ sì tọrẹ àánú kí* <u>*ẹ sì pèsè àpò fún ara yín*</u>*, tí kì í gbó, ìṣúra ní ọ̀run tí kì í tán, ní ibi tí olè kò lè súnmọ́, àti ibi tí kòkòrò kì í bà á jẹ́. Nítorí ní ibi tí ìṣúra yín gbé wà, níbẹ̀ ni ọkàn yín yóò gbé wà pẹ̀lú.*

—Lúkù 12:33-34

Ẹ sì pèsè àpò fún ara yín, ìṣúra ní ọ̀run tí kì í tán, ní ibi tí ẹnikẹ́ni kò lè súnmọ́ látì gbàá lọ́wọ́ rẹ. Ẹ jẹ́ kí ohun kan yé wa síwájú si. Jésù kò sọ pé o gbọdọ̀ ta ohun gbogbo tí o ní kí o wá wà ní ipò àìní kí ó tó le lọ sọ́run Rántí pé, Páùlù na ni ẹni tí ó kọ 2 Kọ́ríntì 9 níbití ó ti sọ pé a sọ wá di ọlọ́rọ̀ nínú ohun gbogbo kí á le máa pọ̀ si ní isẹ́ rere gbogbo. Níbíyi Páùlù kò sọ pé tí o bá lówó lọ́wọ́ tàbí ní ọrọ̀ jẹ́ ẹ̀sẹ̀ tàbí ohnu tí kò dára. Jésù ńsọ pé tí owó àti nkan tí o bání *ni ó wà ni ọ́,* nígbàna kò bá dára kí o tàá kí o wá pèsè ọkàn rẹ fún ìsúra tí kì tán tí o sì jẹ́ ti ayérayé.

Nígbàtí a dàgbà a rí pé a ti sọ owó di òrìsà. Owó ni a fí pèsè fún ohun gbogbo tí a nílò ní ayé, síbẹ̀síbẹ̀, ọ̀pọ̀ lówá rí pé, owó le sọra rẹ̀ di ọlọ́run. Ìdí nì yí tí Páùlù se sọ fún Tímótíù láti kìlọ̀ fún àwọn ènìyàn tí ó ní ọrọ̀ láti lò se ìtọrẹ àánú àti jẹ́ ẹni tí ó ńsoore kí wọn ba le wà ní ìlera pípé nínú èmí. Ọrọ́run fún ọ̀kàn ènìyàn láti sọ owó di òrìsà. Tí ò bá jẹ onínurere ènìyàn tí ó lawọ́ èyí jẹ aporó ìmọtara ẹni nìkan. Má se àánú nígbà gbogbo.

*Kìlọ̀ fún àwọn tí ó lọ́rọ̀ ní ayé ìsinsin yìí kí wọn ma ṣe gbéraga, bẹ́ẹ̀ ni kí wọn má ṣe gbẹ́kẹ̀lé ọ̀rọ̀ àìdánilójú, bí kò ṣe lé Ọlọ́run alàààyè, tí ń fi ohun gbogbo fún wa lọ́pọ̀lọpọ̀ láti lò; Kí wọn máa ṣoore, kí wọn máa pọ̀ ní iṣẹ́ rere, kí wọn múra láti pín fún ni, kí wọn ni ẹ̀mí ìbá kẹ́dùn; kí wọn máa to ìṣúra ìpìlẹ̀ rere jọ fún ara wọn dé ìgbà tí ń bọ̀, kí wọn lè di ìyè tòótọ́ mú.*

—1Tímótìù 6:17-19

Kíyèsi ohun tí Páùlù sọ fún Tímótíù pé kí *ó kìlọ̀*, kì íse pé kí ó *dábá,* fún àwọn tí o lọ́rọ̀ láti jẹ́ ẹniti ó ńsoore àti máa pín fún ni. Rántí pé a nílò owó, sùgbọn kì íse ìyè.

**Toríbẹ ńibo ni ìsúra rẹ wà?**

Ìfifúnni kò mú kí ọkàn Ọlọ́run àti ènìyàn rò nìkan, bíkòse pé ó tún tu ohun tí owó ti dè ní ọkàn rẹ. Okàn le máa se ìlara àti tẹríba fún ohunkohun tí o bá gbé síwájú rẹ, toríbè a kò ní fi ọkàn wa sílẹ̀ kí o má kiriká láìnídi. A gbọdọ̀ fi Ọlọ́run kọ́ ọkàn wa bí orísun wa. Ìfifúnni máa dojúkọ ojúkòkòrò tí ó rọrùn láti máa bá ọkàn wa jagun.

Torí kínni o fi yẹ kí á fi gbogbo rẹ̀ sílẹ̀? Kílódé tí Ọlọ́run kò se ràn ẃa lọ́wọ́ lóri ìsúná wa láì jẹ́ pé a se ìfifún ni? Ìbérè tí ó dára ni, a ó sì rí ìdáhùn nínú Lúkù orí kẹrin.

Àkọ́kọ́, Ọlọ́run kò ní owó, gẹ́gẹ́ bí mo ti sàlàyè sáájú. Ẹ̀kejì, Ó fún Ádámù ní ohungbogbo láti jọba lé lórí nínú ayé, bí wọn ti kọ nínú Hébérù 2:7-8.

> *Lójúkan náà, èṣù sì mú un lọ sí orí òkè gíga, ó sì fi gbogbo ilẹ̀ ọba ayé hàn án. Èṣù sì wí fún un pé, "Ìwọ ni èmi ó fi gbogbo agbára yìí àti ògo wọn fún: nítorí á sá ti fi fún mi. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì wù mí, èmi a fi í fún. Ǹjẹ́ bí ìwọ bá foríbalẹ̀ fún mi, gbogbo rẹ̀ ni yóò jẹ́ tìrẹ."*
>
> *Jesu sì dáhùn ó sì wí fún un pé, "Kúrò lẹ́yìn mi, Satani, nítorí tí a kọ̀wé rẹ pé, 'Ìwọ foríbalẹ̀ fún Olúwa Ọlọ́run rẹ, òun nìkan ṣoṣo ni kí ìwọ kí ó sì máa sìn.'"*
>
> —Luku 4:5-8.

Ibití a kọ láti inú ìwe mímọ yì jẹ ibití Sàtánì ti ńdán Jésù wò ní aginjù. Sàtánì sọ fún Jésù pé gbogbo àsẹ àti ògo orílẹ-èdè ayé yí ni a ti fún òun. Bẹ sì ni ó rí, Ádámù ni ó wà ní ipò na ó sì ti gbé lé Sàtánì lọ́wọ́ nígbàtí ó dìtẹ̀ sí Ìjọba Ọlọ́run.

Ògo ti orílẹ̀-èdè sì ni ọ̀rọ̀ rẹ̀, àti agbára jíjọba lórí ọrọ̀ àti àwọn orílẹ èdè owó ni Sàtáni ti njọba. Má jẹ́ kí o rú ọ lójú—wọn kò sọ pé Sàtáni ti

gba *àsẹ* lórí ògo ayé fún ara rẹ̀. Tí Olúwa ni ilẹ̀ àti ẹ̀kun rẹ̀. Wọ́n kò sọ pé Sàtáni ni *ẹ̀tọ́ láti gba* ọrò àwọn orílẹ̀–èdè.

Tí o bá mú ẹyọkan owó dání tí ó si wòó dádá, àwọn orílẹ-èdè tí ó ńlò owó nà ni ó ní àsẹ lórí owó tí wọ́n ntẹ̀. Nítorí ohun tí Ádámù se, kò jẹ́ kí Ọlọ́run le gba ojúlówó tàbí ayédèrú owó orílẹ̀-èdè. Síbè, bí Ọlọ́run bá le rí ẹnìkan lórí ilẹ̀ ayé tí ó bá gbàgbọ́ nínú rẹ̀ tí ó sì fẹ́ láti fúnrúgbìn owó sí sàkáni àti àsẹ Rẹ̀, nígbàna Ọlọ́run yóò lo ànfàní yi láti wá dá sí ipò na.

Bákanna, lẹ̀ẹ̀kansi, Ọlọ́run kò ní owó, kínni nkan tí mo ńsọ nígbàtí mo bá ní kò le dá sí owó ìsúnam wa? Bíotijẹ́pé Ọlọ́run kò le se májíkì láti pé kí owó jáde bẹ́ẹ̀ (èyí yóo jẹ́ on tí kò bá òfin mu nítorí àìlẹtọ tí Sàtánì ti gbà á), Ó le ràn ọ́ lọ́wọ́ láti gbà tàbí nim ọrọ̀.

**FÍFIFÚN ỌLỌ́RUN WÁ ŃSÍLẸ̀KÙN FÚN ÌDÁPADÀ, ÒFIN TÓ SE PÀTÀKÌ PÚPỌ̀ NI ÌJỌBA. À ŃKÁ OHUN TÍ A BÁ GBÌN.**

Gẹ́gẹ́ bí òfin tí mo tọ́kaśi śaájú nínú ìwé yí, lílawọ́ fún ọ̀run ní òfin sàkání–agbára láti gbà àgbàsílè ti ìdarí àti ìtọ́nísọ́nà fún ẹnìkan nípa ti ìsúná nígbàti wọ́n bá fifúnni. Rántí ìtàn ẹja nínú Lúkù orí karùn? Pétérù mọ̀ ọ́n mọ̀ yá Jésù ní owó nínú oko-òwò ọkọ̀–ojú omi fi wàásù láti ibi lẹ̀kùn tí ó sí sílẹ̀ fún Ẹ̀mi Mímọ́ tí ó tọ́ka ibiti ẹja wà nínú ibú omi.

Fífifún Ọlọ́run wà máa ṣí àwọn ìlẹ̀kùn ayípadà. Òfin kàn tó se pàtàkì nínú ìjọba Ọ̀run ni. A màa ká ohun tí o bá gbìn

Toríbẹ̀ kí ma fa ọ̀rọ̀ náà gùn, à ńpèsè àpamọ́wọ́ fún ara wa nípa fífi sí inú Ìjọba àti iṣẹ́ Ọlọ́run. Ìfifún ni wa fún wa ni ọnà àbá wọlé sínú ọrọ̀ ti Ọ̀run, ìdí sì nì yìí ti Pàulù fí pé "fífi fún" ni àpò wa Èyí sì yí ohungbogbo nínú ayé wa padà.

> *Bẹ́ẹ̀ ni a ó sọ yín di ọlọ́rọ̀ nínú ohun gbogbo, fún ìlawọ́ yín gbogbo tí ń ṣiṣẹ́ ọpẹ́ sí Ọlọ́run nípa wa.*
>
> —2 Korinti 9:11 (EHV)

Sàkíyèsí ohun tí Bíbélì sọ pé *ó sọ yín di ọlọ́rọ̀*, kì sé pé wà máa *jìjàkadì láti di ọlọ́rọ́* nínú agbára àti ọgbọ́n, Ráŕa, o ti ní alábasisẹ́pọ̀ titun —Ẹ̀mí Mímọ́—ó sì mọ púpọ̀ nkan ju bí o ti se mọ̀ lọ.

Mo rántí ìgbá tí a se aláìní fún ọdún mẹsan tókún fún wàhálà. Owó, tàbí kín kú sọ pé ìbẹ̀rù pé a kò ní owó tótó, mu mi lọ́kàn gan. Bíotilẹ̀jẹ́pé Krìstíánì ni mi, mi ò tí fi ìgbẹ́kẹ̀lẹ́ mi sínú Ọlọ́run tóo fún ọkàn mí láti le gbẹ́kẹ̀lé láti le bá mi fọ ètò ègún ayé ní ayé mi Mo ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú àsìse ti ìsúra! Ní ìgbàyí gan, mo nim ìgboyà nínú ara *m*i ó sì jẹ́ ǹkan tí kòdára tó.

Ọlọ́run wá ní láti sọ fún mi bí mo ti se le pèsè àpò fún ara mí tí màa fi n le gba ore–ọ̀fẹ́ àti agbára rẹ̀. Mo sì mọ̀ pé ẹnikẹ́ni tí ó bá mọ̀ mi mọ bí Ọlọ́run ti bá mi sé, Mo tún fẹ́ so ìtàn ná díẹ̀ báyi bóyá ìwọ kò mọ̀ bí Olúwa ti bá mi sé. Sé o mà pé Ọlọ́run ní àwọn ète tí ó dára, O mọ̀ bí ó ti se le dé ọ̀dọ̀ gbogbo wa.

Mo fẹ́ràn kí ń má sọdẹ agbọ̀nrín ṣugbọ́n bí ọdún mẹrin ni mi ò fi rí ẹran kankan pa tí mà sì padà sílé lọ́wọ́ òfo. Mà jáde lọ, jókòó sínú otútù, mo sì ńlọ léra wọn ní gbogbo ọjọ́ tí nkò sì rí ẹran pa. Kì íse èyi nìkan èmi gan fẹ́ràn kín máa sọdẹ ẹran kiri. Mo ní àwọn ọmọ láti bọ ó sì dájú pé a bá má fi èyí rí óunjẹ jẹ. Bíótílèjẹ́pé mo ti ní àwọn àseyọrí kan sáajú rí. Ó ti pẹ́ tí mo ti pa àgbàrín àti mú ẹran wálé.

Ní ojọ́ kan, bí mo ti se ńronú nípa àsìkò sísọdẹ àgbọ̀nrín tọ̀dún yí tó nbọ̀, mo gbọ ohun Olúwa. Tó wípé, Kílóse tí ò jẹ́ kín fi hàn ọ́ bí wà ti se le rí àgbọ̀nrín lọ̀dún yì?"

Bí mo ti bẹ̀rẹ̀ lójijì nì yíi "*Kín fi hàn ọ bí o ti se le rí àgbọ̀nrín ní ọdún na"* Kínni èyí túmọ̀sí? Gígbàdúrà nípa àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí, mo rò pé o yẹ kiń fúnrúgbìn èso, tàbí ẹ̀bùn, fún ìdí èyí àti kórè àgbọ̀nrín nà. Mo rò pé ohun tí Olúwa ńsọ fun mi nipé, tí mobá ti fúnrúgbìn fún àgbọ̀rín mí,mo ní ìgbàgbọ́ pé mo ti rí gbà ná, gẹ́gẹ́ bí Mákù 11:24 ti so.

> *Nitorí náà, mo wí fún yín ohunkóhun tí ẹ bá béèrè fún nínú àdúrà, ẹ ní ìgbàgbọ́ pé, ó tí tẹ̀ yín lọ́wọ́, yóò sì jẹ́ tiyín.*
>
> —Mákù 11:24

Lóòtítọ́, gẹgẹ bí Krìstíánì, gbogbo ìgbà ni mo má fifúnni àti gbárùkù ti ìjọ mi. fúnrúgbìn bí irú èyí, pẹ̀lú àfojúsùn àti ìgbàgbó pé mà rí gbà tí mo bá gbàdúrà, jẹ titun.

Mo mú sòwédowó mi mo sì kọ sí pé, Fún àwọn àgbàriń mi tí ọdún 1987" Mo gbọ́wọ́ lé mo sì pàsẹ pé mo ti gba àgbọ̀nrín bí mo ti fi ìgboyà

firánsẹ sí ilé isé ìránsé.

Nítorí tí mo ńgbé ní Tulsa, ní Oklahoma, ìlú yi nà tún kún ìdí tófa, mi ò rí ibi tí mo ti le lọ sọdẹ, sùgbọ́n ọ̀rẹ́ mi kan láti inú ìjọ sọ fún mi láti wá sí ilé mọ̀mọ́ wọn àgbà ní ìlú fún Ìdúpẹ́, ó sì ní àwọn àgbọ̀nrín díẹ̀ ti ẹ̀ wà ní àyíká oko wọn. Toríbẹ̀, èmi àti ìdílé mi gba ibi Ìdúpẹ́ nà lọ ní òwúrọ̀ lamti le gbádùn ọjọ́ nà ní ti ounjẹ àti ìdàpọ̀, àti fún àgbọ̀nrín.

Ọ̀rẹ́ mi kò tilẹ̀ mọ ibití om yẹ kín lọ, sùgbọ́n mo rí pápá oko kan tí ó pàlà pèlú igi, ó sì dàba kín gba ipa pápá oko nà kí si jókòó lórí igi ńla kan tí ó wà níbè.

Mo fẹ́ kí o fi ojú inú wo àwòrán yi. Mo jókò lóri àgékù koríko ní pápá oko tí igi ńla kan ṡi wá ní àrin rẹ̀. Mo wá wò pé nígbàna lọ́un, mo jókòó lórí pápá ńlá ní orí igi. Bí ilẹ̀ ti mọ si, mo ròo wípé. *Pé kínni yí kò ni le sisé báyi kín jókòó ní gbangba. Mo ní láti wà ibi ti ó tún dára sí jókòó.*

Bí mo ti se ńronú pé kín ńdìde àti lọsíwájú àwọn igi, mi kò sàkíyèsí ohun tíi o nsẹlẹ̀ lẹ́yìn mi ní ẹ̀gbẹ́ kejì ibití igi wà. Láìjẹ́pé mo mọ̀ pé, àgbọ̀nrín ńlá kan ti ńsáré kọjá sí òdìkejì lẹ̀yìn mi. Igi wà lárìn èmi àti àgbọ̀nrín nà, ẹran yí kò rí mi, èmi na pẹ̀lú kò sì rí. Àgbọ̀nrín sáré sí ibití igi wà, o gbúro mí ó wá dúró lójijì bí ó ti ńgbìyànjú láti mọ nkan tí ó ńsẹlẹ̀.

Bí àgbọ̀nrín nà ti dúró mọ́ ọ̀kan ibiti igi na wà, ojú wa pàdé. Àgbonrín nà kò ju bí ọ̀pá ẹsẹ̀ márun sí ọ̀dọ̀ mi lọ! Àgbọ̀nrín nà kò fi àkókò rẹ̀ sòfò ó gbéra ńlẹ̀. Pẹ̀lú ariwo ẹ̀fẹ̀, ó yára ńsaré lọ.

Nígbàna mo wá gbà pé èmi kì íse ẹni tó mọ ìbọn yìn. Bí mo ti ńwo ìrù funfun àgbọ̀nrín yí lọ tí ńsáre kíkankíkan lọ kúrò ní ibití mo wà kò fún mi ní ànfàní ńlá, ẹlekejì, láti tún yìnbọn ní ibiti mo wà tí íse 30-06 kì íse ibití ó rọrùn láti yìnbọn. Sùgbọ́n nígbàtí mo yin ìbọn mí mọ́, àgbọ̀nrín nà dàlulẹ̀ kò sì le mira mọ́. Àyà mí já! Bí ọ̀rẹ́ mi ti gburo ìbọn, ó jáde wá om sì kí mí kú oríre fún àgbọ̀nrín tí mo pa, bí o ti se ri ti ó wà nilẹ̀ níbè. Èmi ò sì ti sọ fún ọ̀rẹ́ mi nípa ohun tí Olúwa sọ fún mi, sùgbọn mo wòó mo sì sọ pé, mí ò rò pé nípa agbára tàbí mímòse mi ní èyí"

Mo mú ìwé tí mo kọ ní ọjọ́ tí mo kọ sọ̀wédowó ránsẹ́ fún ti àti lọ sọdẹ mi. Ohun tí ó sọ na nipé "Mo gbàgbọ́ pe mo ti rí àgbọ̀nrín ọdún 1987 mi gbà, ní orúkọ Jésu." Mo ní ọjọ́ àti àkókò tí mo gbàdúrà tí mó sì kọ sílẹ̀. Mo fi ìwé nà hàn ọ̀rẹ́ mi láti wo mo ẃa bẹ̀rẹ̀ sí ní sọ fún nípa ohun tí Olúwa sọ fún mi láti se.

Ìsẹ̀lẹ̀ yí jé kín mọ̀. Mo sì mọ láìsiyè méjì pé Ọlọ́run ni ó se àgbọ̀nrín na. Bẹ́ẹ̀ni, nígbàti ó bá rí ńkan tó rí báyi, ọkàn rẹ yóò maa sọ fun ọ pé oríre ni. Sùgbọ́n láti bí ọdún mẹ́rìn-lé-lọ́gbọ̀n, ni mo ti n kórè àgbọ̀nrín ní ọ̀nà yí bákanna bí mo ti se ti 1987, laíkùnà, tí kò sì tó bí wákàtí kan ní ìdí igi.

Ọlọ́run ńlo ọ̀nà kanna láti dé ọ̀dọ̀ Pétérù, Jákọ́bù, àti Jòhánnù ní ètí adágún odò ní ọjó nà ní Génésárétì. Bíbeli sọ pé ohun ti wọ́n rí sì yá wọ́n lẹ́nu.

> *Ẹnu sì yà wọ́n, àti gbogbo àwọn tí ń bẹ pẹ̀lú rẹ̀, fún àkópọ̀ ẹja tí wọ́n kó: Bẹ́ẹ̀ ni Jakọbu àti Johanu àwọn ọmọ Sebede, tí ń ṣe alábákẹ́gbẹ́ Simoni.*
>
> *Jesu sì wí fún Simoni pé, "Má bẹ̀rù; láti ìsinsin yìí lọ ìwọ ó máa mú ènìyàn." Nígbà tí wọ́n sì ti mú ọkọ̀ wọn dé ilẹ̀, wọ́n fi gbogbo rẹ̀ sílẹ̀, wọ́n sì tọ̀ ọ́ lẹ́yìn lọ.*
>
> —Luku 5:9-11

Ẹnu sì yà wọ́n, wọ́n fi gbogbo rẹ̀ sílẹ̀, wọ́n sì tọ̀ Jésù lẹ́yìn lọ. Wọn tún ti rí ọ̀nà tí ó dára láti má gbà se nkan.

Gẹgẹ́ bí Ọlọ́run ti se fi ìjọba òrun hàn mí àti bí ó ti pèsè àpò fún mi (ojú ọ̀nà àbáwolé sì ibi ìsúra mi ní ọrun) Tí mo nílò, kí ọkàn mí má dàgbà sí ní ìgboyà nínú àwọn orísun mí tí ọ̀run ju àwọn ńkan tí mo kódání ni owó mi lọ.

Ọlọrun kọ̀ mi pé mo le fúnrúgbìn fumn ohunkóhun ti mo bá nílò,bóyá ni yóò fún mi ní ètò láti sẹ̀dá fún mi ní ètò láti yàwòrán rẹ̀. Kò sí ayè fún mi ńibiyi láti pimn gbogbo àwọn ohun tódara tí mo ti rí bí èsì ti Ijọba, Sùgbọ́n mo le sọ pé Èmi àti Drenda tí àwọn nkan aláràgbàyimdam tí ó ti sẹlẹ̀ nínú ìsúná wa. Láti ipò àìní nkankan sí tí a wá di ẹni tí ó ní owó dé ibi pé àwa na sátìlẹ̀yìn fún àwọn ilé isẹ̀ ìránsẹ̀ nípa nínà milliọ́nù láti ọ̀pọ̀ ọdún ó jẹ́ ohun ìyanu.

Tí a ńfi ìgbàgbọ fúnrúgbìn fún ìkórè kan pàtó ní ohun tí Ọlọ́run kọ́kọ́ kọ́mi bí mo ti se bẹ̀rẹ̀ sí ńikọ́ nípa Ìjọba. Bíótìlẹ̀jẹ́pé àyè kò sí fún mi tó láti sọ ohungbogbo, ńinú àwọn iwè mí míràn wa sì rí àwọn ìtàn bí Ìjọba tí sẹ jẹ́ ǹkan pàtó àti bí irúgbìn rẹ na tí se nílò láti jẹ pàtó. *Yíyí Ètò Ìsúnà Rẹ Padà: Àgbára ti nìpèsè* ìwé yi kún fún bí ó ti se le lo ìgbàgbọ́ rẹ bí o sì ti se

le fúnrúgbìn, èso rẹ pàtó ju bí ìwé yi ti sọ lọ. Mo gba ọ níyànjumi láti ra ìwé nà kí o sì kọ́ nípa àkòrí ẹ̀kọ́ nà si dáda.

Ìwé yi sọ àwọn kókó ọ̀rọ̀ nípa ìlànà àwọn òfin tí Ọlọ́run kọ́ mí ńipa bí ó ti se jẹ́ oninúrere àti afífún ni. Mólérò pé wọ́n gbà ọ́ nìyànjú àti mú ọ lórí yá láti fẹ́ mọ si àti jẹ́ ohungbogbo tí Ọlọ́run ní fún ọ.

ORÍ KẸ̀SÁN AN

# Ọ̀FIN TI OSUNWON

Bí osù mélo kan sẹ́yìn èmi àti Drenda lọ fúnrúgbìn ẹ̀ẹ́dẹ́gbàjọ pọ́ùn sí ilé isẹ́ ìránsẹ́ kan. Bí mo ti fẹ́ sọ ọ̀rọ̀ ìgbàgbọ́ mi jáde, ni Emí Mímọ́ ránmilétí ìwé 2 Kọ́ríntì 9 :10 -11, ẹse ìwé mímọ́ yi ni mò sì wá níran fún bí ọjọ́ díẹ̀ lẹ́yìn ìgbàna.

> *Ǹjẹ́ ẹni tí ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ, yóò fi irúgbìn fún un yín, yóò sì sọ ọ́ di púpọ̀, yóò sì mú èso òdodo yín bí sí i. Bẹ́ẹ̀ ni a ó sọ yín di ọlọ́rọ̀ nínú ohun gbogbo, fún ìlawọ́ yín gbogbo tí ń ṣiṣẹ́ ọpẹ́ sí Ọlọ́run nípa wa.*
>
> —2 Kọ̀ríntì 9:10-11

Mò ńse àsòrò lórí ipa tí ó sọ pé Ọlọ́run tí ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ, “àkàrà fún oúnjẹ,” fò sókè nínú mi. Mo sì mọ̀ pé ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ní ẹ̀rù máa ńbà nígbàti wọ́n bá fẹ́ se ìfifún, nítorí tí wọ́n kò ní òye ńkan yìí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ní wọ́n lérò pé nígbàtí wọ́n bá se ìfifún ni, wọ́n ńfi nkankan sílẹ̀ ni, ti ó sì ma *ná* wọn níkan. Sùgbọ́n ohun tí Ọlọ́run rán mi léti rẹ̀ ni pé kì ise pé yóò fi irúgbìn fún afúnrúgbìn nìkan, láti gbín, sùgbọ́n pé yóò tún pèsè àkàrà fún oúnjẹ tàbí nkàn tí ènìyàn bá nílò fún ara rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ni, Mo ti mọ èyí tẹ́lè, sùgbọ́n mo rò pé Ó fẹ́ rí dájú pé mo sọ fún gbogbo ènìyàn pé—o fi méjèjì fún wa a kò sì gbọdò bẹ̀rù láti fifun ni.

Ní alẹ́ ọjọ́ tí a ńsọ yìí, bí ọ̀sẹ̀ méjì lẹ́yìn ìgbàtí tí a ti fúnrúgbìn ẹ̀ẹ́dẹ́gbàjọ pọ́ùn, Mo fẹ́ lọ pa iná kín sì bọ sí orí ìbùsùn mi nígbàtí, lójijì, èrò kan tọ̀ mí wá pé kín lọ yẹ àwọn ọjà kan wò kí nsìwó bí wọ́n ti se ńtà sí ní ọjà. Mo lọ wo àsùnwọ̀n mi, mo rí pé owó díẹ̀ ti sunjọ sí bẹ̀ si.

Bí mo ti fẹ pa ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ mi mo tajú kán mo sì rí ọjà kan tí kì íse èmi ni mo ní. Mo ti rí ọjà yìí tẹ́le, mo wá wo pé bóyá kin kúkú ra lẹ́kanna, nígbàtí mo se ìwádi lóri rẹ̀, mó wá rí pé láti bí osù méjìlá ni ó ti wà níbè tí kò réyàn rá mo ya kọjá rẹ̀ lọ.

Sùgbọ́n fún ìdíkan, ní alẹ́ ọjọ́ yi, ọjà sàdédé lọ sókè lójú mi. Ó sàjòjì sí mi, mo sá wo pé kín sá ra ǹkan lára ọjà ní ọjọ́ nà. tí èmi kì se bẹ. Kò sí lára ìwà mi. Mo wá lọ ra ọjà bi o ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ́jọ pọ́ùn ńi ara ọjà na mo sì pa fónù mi.

Èmi àti Drenda sọ̀rọ̀ fún ìgbà díẹ̀, mo sì sàlàyé fún nípa ọjà tí mo rà. Mo sì tan fónù mi láti fi hàn. Nígbàtí mo tan fónù tán, ìyàlẹ́nu ní ó jẹ́ fún mi. Mo ti jère ̀idá ọgọ́run láàrin wákàti kan! A kò sùn mọ́ a sì bẹ̀rẹ̀ sí ní wòó bí ó tí ń lọ tí ò sí ńga sókè díẹ̀díẹ̀.

Nígbàtí ó fi máa tó wákàtí mẹ́ta, ọjà na ti lọ sókè dé ẹ̀ẹ́dẹ́gbàsán pọ̀ùn, ni ó ti dé. Mo sọ fún Drenda, pé ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ́jọ pọ̀ùn wa nì yí o!"

Mo tètè ta ọjà na mo sì yàwòrán iye tí ó lé sí. Ọjà nà wá tún lọ sẹ́yìn ní òwúrọ̀ ọjọ́ kejì kò sì tún tì dé ìpele bó se pọ̀ sókè mọ́ láti bí osù mélo láti ìgbà na. tó ti sẹlẹ̀. Ó jẹ́ ǹkan tó ti burú jài tí mo ti rí rí. Èmi mọ̀ pé Ẹ̀mí Mímọ́ ni tí ó tànmọ́lẹ̀ sí ọjà na fún mi, mo sọ fún Drenda pé ọ̀nà tí Ọlọ́run fi dá èso wa padà ni. Ọlọ́run tí ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ.

Sùgbọ́n ó jẹ́ ohun tí ó dára gan. Lẹ́yìn tí mo ti ta ọjà ná tán tí owó sì ti wọ inú àpò àsùnwọn mi, mo wá ròò pé, *"Ọmọ tí, mo bá mọ̀ pé yóò tètè jáwọ̀ báyi ni, mi ̀o bá kó owó tí ó ju ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ́jọ pọ̀ùn lọ le lórí.* Mo wá wò pé nígbogbo ìgbà 20/20 ni ó má sábà jẹ́. Bẹ́ẹ̀ni, ńse ni mi ò bá kó *ẹgbàárún pọ̀ùn* lé ọjà na lórí, tàbí kínni o ńrò*, Ó da tí mo bá wá lọ kó ọ̀kẹ́ màrún pọ̀ùn le lórí ńkọ́? Mo rò ẃipé iye owó tí mà jèrè lórí ìdókòwò na*. Sùgbọ́n mi ò kó ẹgbàárún pọ̀ùn le lórí. bẹ́ẹ̀ni mi ò fi ọ̀kẹ́ màrún pọ̀ùn si. Kódà *mi ò fi* ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta pọ̀ùn sí iye tí mo kó lé ni ẹ̀ẹ́dẹ́gbàjọ pọ̀ùn.

Bíbélì sọ fún wa nínú Lúkù 6:38 ohun tí ó sẹlè, kílódé tí mi ò fi jèrè owó púpọ̀ ní alẹ́ ọjó nà.

> *Ẹ fi fún ni, a ó sì fi fún yín; òṣùwọ̀n dáradára, àkìmọ́lẹ̀, àti àmìpọ̀, àkúnwọ́sílẹ̀, ni a ó wọ́n si àyà yín: nítorí òṣùwọ̀n náà tí ẹ̀yin fi wọ́n, òun ni a ó padà fi wọ́n fún yín."*
>
> —Luku 6:38

Sé o ti rí, mo ti fi òsùnwọ̀n wọn kalẹ̀, òsùnwọ̀n tí mo sì fi wọ̀n ni wọn fi wọ̀n padà fún mi, èrè tí mo jẹ ní alẹ́ ọjọ́ nà jẹ́ déédé iye tí mo ti wọ̀n sílẹ̀. Mo ti wọn òsùnwọ̀n, pẹ̀lú òsùnwọ̀n yí kanna ni mo fi gbà á padà. Jésù sọ pé òfin yìí kanna ni fún bí o ti se ńse ìfifún ni.

Ìtàn kan wà nínum Bíbéli mo fẹ́ fi hàn ọ́ níbiti o ti sẹlẹ̀. Ale kọ ẹ̀kọ́ tópọ̀ níbẹ̀ nípa òfin ti òsùnwọ̀n.

*Ìyàwó ọkùnrin kan láti ara ẹgbẹ́ wòlíì sọkún tọ Eliṣa wá, "Ìránṣẹ́ rẹ ọkọ mi ti kú, ó sì mọ̀ wí pé ó bu ọlá fún* OLÚWA*. Ṣùgbọ́n Nísinsin yìí onígbèsè rẹ̀ ti ń bọ̀ láti wá kó ọmọ ọkùnrin mi gẹ́gẹ́ bí ẹrú rẹ̀."*

*Eliṣa dá a lóhùn pé, "Báwo ni èmi ṣe lè ràn ọ́ lọ́wọ́? Sọ fún mi; kí ni ìwọ ní ní ilé rẹ?"*

*"Ìránṣẹ́ rẹ kò ní ohunkóhun níbẹ̀ rárá," Ó wí pé, "àyàfi òróró kékeré."*

*Eliṣa wí pé, "Lọ yíká kí o sì béèrè lọ́wọ́ gbogbo àwọn aládùúgbò fún ìkòkò òfifo. Má ṣe béèrè fún kékeré. Nígbà náà, lọ sí inú ilé kí o sì pa lẹ́kun dé ní ẹ̀gbẹ́ ìwọ àti àwọn ọmọ rẹ ọkùnrin, dà òróró sínú gbogbo ìkòkò, gẹ́gẹ́ bí gbogbo rẹ̀ ti kún, kó o sí apá kan."*

*Ó sì fi sílẹ̀ lẹ́yìn náà ó ti ìlẹ̀kùn ní ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ àti àwọn ọmọ rẹ̀. Wọ́n gbé ìkòkò wá fún un ó sì ń dà á. Nígbà tí gbogbo ìkòkò náà kún, ó sọ fún ọmọ rẹ̀ pé, "Ẹ gbé òmíràn fún mi wá."*

*Ṣùgbọ́n wọ́n dáhùn pé, "Kò sí ìkòkò tí ó kù mọ́." Nígbà náà ni òróró kò dà mọ́.*

*Ó sì lọ ó sì lọ sọ fún àwọn ènìyàn Ọlọ́run, ó sì wí pé, "Lọ, ta òróró náà kí o sì san gbèsè rẹ. Ìwọ àti ọmọ rẹ kí ẹ máa sinmi lórí èyí tí ó kù."*

—2 Awon Oba 4:1-7

Ìtàn ńlá nìyí tí ó kún fún ọ̀pọ̀ àwọn ìfihàn ti Ìjọba nínú rẹ̀. Obìnrin yí lọ sọ́dọ̀ wòlíì fún ìrànlọ́wọ́m, ó wà nínú gbèsè tí ó sì mú kí ó fé pàdánù àwọn ọmọ rẹ̀. Sùgbọ́n sí ìyàlẹ́nu, wòlíí kò tọwọ́bọ àpò láti fún lówó. Dípòbẹ. Ó bèrè ìbérè kan tó sàjèjì lọ́wọ́ rẹ̀ ninú ipò àyídáyídà tó wà: Sọ

fún mi; kí ni ìwọ ní ní ilé rẹ?

Mo rò pé ìbérè na yóò jọ obìnrin na lójú, bí ó ti se rí nínú ìdáhùn rẹ. "Ìránṣẹ́ rẹ kò ní ohunkóhun níbẹ̀ rárá!" ní ó sọ. Ò tún fi kún pé "ohunkóhun níbẹ̀ rárá!" Sùgbọ́n kò dàrùkọ àwọn nkan tí o ní. Kò kí ise ohnu tó pọ̀, sùgbọ́n àyàfi òróró kékeré." Gbogbo ohun tí wòlíì fẹ́ gbọ́ nìyí. Ìdáhùn na sì ni. Kíyèsí àwọn ìtóni yí dáda.

> *Eliṣa wí pé, "Lọ yíká kí o sì béèrè lọ́wọ́ gbogbo àwọn aládùúgbò fún ìkòkò òfìfo. <u>Má ṣe béèrè fún kékeré.</u>*o.

Má ṣe béèrè fún kékeré. Má lọ nì yen? Mo lérò pé wà gbà pẹ̀lụ́ mi pé iye ìkòkò tí yóò kójọ wá di ọ̀rọ̀ àríyanjìyàn tí ó jẹ́ pé òun nìkan ni ó le sọ ohun tí o túmọ̀ sí fún un. Ó wá rí wípé òun kò kó ìkòkò tí ó tó jo!

> *Ó sì fi sílẹ̀ lẹ́yìn náà ó ti ìlẹ̀kùn ní ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ àti àwọn ọmọ rẹ. Wọ́n gbé ìkòkò wá fún un ó sì ń dà á. Nígbà tí gbogbo ìkòkò náà kún, ó sọ fún ọmọ rẹ̀ pé, "Ẹ gbé òmíràn fún mi wá."*
>
> *Ṣùgbọ́n wọ́n dáhùn pé, "Kò sí ìkòkò tí ó kù mọ́." Nígbà náà ni òróró kò dà mọ́.*

Kíyèsi pé nígbàti òróró kò dà mọ́–kì íse pé ó ti pé iye ìkòkò tí ó jẹ́ bíkòse nígbàtí kòsí ìkòkò mọ́ ni. Nígbàti gbogbo ìkòkò ti ó ní ti kún, ó sọ fún ọmọ rẹ pé kí ó tún gbè ìkòkò míràn wá, kí ó tó sọ fún pé kò sí ìkòkò mọ́. Mo mọ pé kò bá fẹ́ kí ó sì maa tẹsíwájú bẹ̀ lọ, sùgbọ́n àwọn ìkòkò púpọ̀ dìẹ̀ ní ó kójọ. Pípòsi rẹ kún kì íse nípa ti Ọlọ́run bíkòse nípa tí èrò ara rẹ.

Mo mọ̀ dájú pé kò bá fẹ́ kí òun sì ní ọ̀pọ̀ ìkòkò sí,ọpọ̀lọpọ̀ ìkòkò. Tí o bá jẹ́ pé o mọ nkan tí o fẹ́ sẹlẹ̀ ni, mo mọ̀ pé gbogbo ìlẹ̀kùn ara àdúgbò rẹ pátá ni kò bá lọ kàn láti gba ìkòkò jọ. Kódà kò bá tún ránsẹ́ sí àwọn ìlú míràn lágbègbè láti kó ìkòkò jọ.

Ìtàn na ni àbájáde ti ó dára bíótìlẹ̀jẹ́pé: ó san gbogbo gbèsè rẹ àwọn ẹbí ẹ̀ sì ńgbé ayé wọn lọ lẹ́yìn tí ó ti ta òróró nà tán.

Sùgbọ́n kín ni àbájáde rẹ kòbájẹ́? Kò bá san gbogbo gbèsè *gbogbo àwọn ẹnití* ó mọ̀,kí ó tún ọjà ìlú kọ́, kí ó sì tún ran ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn lọ́wọ́.

Kí wá lódé tí ó lọ kó iye ìkòkò tí ó kó jọ yi? mo rò wípé làákàyè bí yóò sá ti bọ́ nínú gbèsè ni ó nim, Ò sì tún wo gbogbo wàhálà tí ó nlà kọjá—iye gbèsè tí ó jẹ́ àti ohun tí yóò fi tọ́jú àwọn ọmọ rẹ̀! Dípò kí ó ronú kọjá àlàkọjá tí ó ńdojúkọ, ohun tí ó wà lọ́kàn rẹ̀ nipé kín sá yanjú ohun tó wà nílẹ̀ ná. Mo sì gbàgbọ́ pé tí o bá kó ẹgbẹ̀rún ìkòkò jọ, gbogbo rẹ̀ ni yóò kún fún òróró. O ti wọn òsùnwọ̀n ara rẹ̀!

Ọlọ́run fún gbogbo wa ní irú ànfàní tí obìnrin yí ní. Gbogbo wa ni a gbọdọ̀ yàn bí a ti fẹ́ sètò òsùnwọ̀n wa.

Jẹ́kí nsàlàyé bí a ti se ńgbé àwọn kòkò ẹ̀kọ́ fún ìpín yi wo.

> *Ẹ fi fún ni, a ó sì fi fún yín; òṣùwọ̀n dáradára, àkìmọ́lẹ̀, àti àmìpọ̀, àkúnwọ́sílẹ̀, ni a ó wọ́n si àyà yín: nítorí òṣùwọ̀n náà tí ẹ̀yin fi wọ́n, òun ni a ó padà fi wọ́n fún yín."*
>
> —Lúkù 6:38

Gbogbo wa ni a fẹ́ràn láti má ka ipa àkọ́kọ́ ti ìwé Mímọ́ yi—pé tí o bá fifúnni, a o gba padà pẹ̀lú ọ̀polọpọ̀ àkúnwósílẹ̀. Sùgbọ́n ní ọ̀pọ̀ ìgbà, a kì sábà ka ipa tó parí ẹ̀kọ́ nà tí o sọ pé *nítorí òṣùwọ̀n náà tí ẹ̀yin fi wọ́n, òun ni a ó padà fi wọ́n fún yín."*

Ḱi ló fa tí ìlànà òfin yí sese pàtàkì sí ìwọ àti èmi? Ó da, jẹ́ kín se àpẹẹrẹ kan fún ọ.

Jẹ́ kí á wò pé àgbẹ̀ tí ó sẹ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀d sí dá oko tí mo wá sọ fún pé mo fẹ́ra àwọn ìtí ọkà àlìkámà Tí ìwọ àti èmi sì wá se àdéhùn lórí iye tí ó fẹ́ ta ìdì kan, ó wá palẹ̀ ilẹ̀ oko mọ́ láti gbin sí bí saarè Mẹwa ilẹ̀ pápá oko pẹ̀lú ọkà àlìkámà fún ìkórè.

Mo rò pé o mọ nkan tí ó le sẹlè. Wa se ohun gbogbo tí ipá rẹ ká láti se kí o le mú àdéhùn wá sẹ. Kílódé? Nítorí o kò mọ iye saarè ilẹ̀ tí o le tó láti kórè ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta ilẹ̀ oko àlìkámà.

**KRÌSTÍÁNÌ MÉLO NI WỌ́N TO ỌKỌ̀-AKẸ́RÙ SÍLẸ̀ TÍ WỌN PALÈMỌ LÁTI KÓ ERÈ OKO WỌN LỌ SÍ ỌJÀ TÍ Ó SÌ JẸ́ OKO ÈSO TÒMÁTÒ MÉJÌ NÌKAN NI WỌN GBÌN.**

Òsùnwọn ni tí àwọn àgbẹ̀ ní iye saarè ilẹ̀ oko tí wọ́n dá fún àpẹẹrẹ. Ní ti obínrin tí a sọ̀rò rẹ̀, ní iye ìkòkò tí ó rí kó jọ. Nínum àpẹẹrẹ tí Jésù se fún wa, iye tí a bá fúnrúgbìn ni.

Toribẹ̀, tí ìkórè tí a bá ńretí kò bá wà ní dọ́gbadọgba pẹ̀lú ohun tí à retí láti gbà, òfo ni yó já sí, ó séese kí àwọn tí òye wọn kò kún tó má bá Ọlọ́run wí bí pé ọ̀rọ̀ Rẹ̀ ni ó kùnà.

Ìbérè ńla nìyií: tí àgbẹ̀ kan bá nílò ìtí ìdì ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta àlìkámà tí kò sì mọ ònà tim yó gbe gbà iye saarè ilẹ̀ oko tó nílò láti fi gbin èso, kín ni nkan tí yo se.

**Bèèrè lọ́wọ́ àgbè tí ó mo**!

Báyìí e jẹ́ kí á fi òfin yí sínú ipò tí à ńrí ní gbogbo ìgbà.

Àwọn ìdílé kan fẹ́ san owó tí wọ́n jẹ tí ńse ẹ̀ẹ́dẹ̀gbẹ̀ta pọ́ùn wọ́n sì mọ̀ pé àwọn ní láti fúnrúgbìn ọkọ àti ìyàwó wá jọ gbà láti lo ìgbàgbọ wọn. Sùgbọ́n èló ni wọn fẹ́ fúnrúgbìn? Mo ma ńgba irú ìbéèrè yí ní gbogbo ìgbà. Èló ni wọ́n nílò láti fúnrúgbín tí yóo se òdiwọ̀n fún ẹ̀ẹ́dẹ̀gbẹ̀ta pọ́ùn tí wọ́n fẹ́ kòre?. Wọn kò mọ̀. Wọ́n nílò láti bèèrè lọ́wọ́ ẹniti ó mọ̀, ó sì ní láti jẹ́ Ẹ̀mi Mímọ́.

Gbogbo wa ni a ti gbọ́ tí ó ńdáhùn ìbérè ní kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ sí irú àwọn ìbéèrè bá wọ̀nyìí ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Lóòtọ́ tí kò bá sì ìdánilẹ́kọ́ tópé, a kò ní kọbi ara sí ohùn kékeré nà bí ó ti yẹ kí á se. Fún àpẹẹrẹ, bí ó ti ńfúnrúgbìn fún XYZ, o rò pé ó yẹ kí o fúnrúgbìn ẹgbẹ̀rún kan pọ́ùn. Lẹ́sẹ̀kanna, ẹ̀mí rẹ wá sọ pé "Rárá, Mi ò le se bẹ" tàbi èyí tó tún burújù bẹ lọ, "Sàtánì padà lẹ́yìn mi."

Ohun kan tí mo mọ̀ tó dájú nipé <u>Sàtánì kò le sọ fún ọ kí o fúnrúgbìn ohun tó pọ̀ sínú ìjọba Ọlọ́run</u>. Ó mọ̀ dada nípa òfin yí nípa ti Ìjọba Ọlọ́run. Nítorí tí iwọ gan kò tí ní ìgboyà tó tó nínú ìlànà òfin bí à ti sètò òsùnwọ̀n, nígbàtí ọkàn rẹ bá ńba ọ jiyàn, wà gbà wa lọ fi ọgọ́run kan pọ̀ùn sílẹ̀. Bí mo sì ti sọ, bí àpẹẹrẹ ìdí ìtí àlìkámà, wà rípé o má pàdánu ìkórè tí o nílò.

Báyìí kín tó tún má tẹ̀síwájú, mo ní láti jẹ́ kí nkankan yé wa:

Iye owó tí ó fi sílẹ̀ kò sọ nípa iye owó tí o nfúnrúgbìn!

Lọ wo Lúkù 21:1-4:

*Nígbà tí ó sì gbé ojú sókè, ó rí àwọn ọlọ́rọ̀ ń fi ẹ̀bùn wọn sínú àpótí ìṣúra. Ó sì rí tálákà opó kan pẹ̀lú, ó ń sọ owó idẹ wẹ́wẹ́ méjì síbẹ̀. Ó sì wí pé, "Lóòótọ́ ni mo wí fún yín, tálákà opó yìí fi sí i ju gbogbo wọn lọ: Nítorí gbogbo àwọn wọ̀nyí fi sínú ẹ̀bùn Ọlọ́run láti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìní wọn; ṣùgbọ́n òun nínú àìní rẹ̀ ó sọ gbogbo ohun ìní rẹ̀ tí ó ní sínú rẹ̀."*

Kíyèsí ohun tí Jésù sọ pé tálákà opó yìí fi sí i ju gbogbo wọn lọ ani gbogbo àwọn ọlọ́rọ̀ tí wọn fifún ni ọjọ́ na. Àwọn ọlọ́rọ̀ fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó sílẹ̀, sùgbọ́n Bíbélì sọ pé wọn fi sílẹ̀ láti inú ọ̀pọ̀ ọrọ̀ tí wọ́n ní tàbí kí à sọ wípé owó tí ó tún sẹ́kù. Tálákà opó yìí fi gbogbo ohun tí ó ní ní ayé rẹ̀ sílẹ̀, ó sìgbé ìgbésẹ̀ ìgbàgbọ́ ńlá.

O kò nílò ìgbàgbọ́ láti fún ni nínú ọ̀pọ̀ ohun tí o ní. Lóòtọ́ ìfifún ni láti inú àkúnwọ́sílẹ̀ rẹ̀ jẹ́ ohun tó dára láti se, sùgbọ́n ní ọjó nà, àwọn ènìyàn le ri ohun tí àwọn èǹiyàn ńfi sínú igbá ọrẹ, àti àwọn ọlọ́rò ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ni wọ́n fi sílẹ̀ kí àwọn ènìyàn le rí wọn àti kí wọn le gba iyì láàrin àwọn akẹ́gbẹ́ wọn nínú ẹ̀sìn.

Toríbẹ̀ sísètò òsùnwọ̀n nípa iye owó tí ó fi sílẹ̀ kò le dọ́gba àti wà ní déédé pẹ̀lú ìtumọ̀ bí a ti sètò ti òsùnwọ̀n. Ó jẹ́ ipa tí ó tóbi sùgbọ́n kì sé ipa yí nìkan.

láti mọ̀ pé nkan tí ó "tóbi" lọ́dọ̀ ẹnìkan ó se é se kó ma tóbi lọ́dọ̀ ẹlòmíràn.

Ní ìgbà kan rí tí o bá fi ẹgbẹ̀rún kan dọ́llaà sílẹ̀ owó ŃLÁ ni fún mi. kódà, ní ìgbà tí a sẹ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀, ó má gbàwá bí osù díẹ̀ kí a tó le rí irú ọrẹ tótóbẹ̀ san. Sùgbọ́n a dàgbà si nínú agbara, a sì ti fi ọ̀pọ̀ sílẹ̀ bí ìgbàgbọ́ àti ìgbóyà wa ti ńdàgbà sí.

Nkan tí mo má ńsọ fún àwọn ènìyàn ni: Nígbàtí o bá fúnrúgbìn fún ìpèsè, wá àsìkò láti bí Ẹ̀mí Mímọ ní ohun tí ó tọ́ kí o gbìn àti ibiti ó yẹ kí o gbìn sí.

Máa kú sọ pẹ fífúrúgbìn fún ohun gbogbo ìgbà kò nílò ìgbàgbọ́ tó ga bí ìgbà tí o nfúnrúgbìn fún ọ̀nà àbáyọ kan, bí ìgbàtí o fẹ́ san gbogbo gbèsè orí ilé tó ńgbé. Tí mo bá fúnrúgbìn fún àwọn ohun tó se Pàtàkì, mo má *nfé kín mọ̀ ọ́ lára.*

Ohun tí mò ńsọ ni pé mi ò kàn fi sílẹ̀ nínú ọ̀pọ̀ owó tí mo ní. Mo fẹ́ láti

gbìn èyí tí o tó tí mo le mọ̀ lára pé ìgbàgbọ́ mí ńsisẹ́. Iye owó nà gbọdọ̀ tóbí tó ohun tí ẹran ara mi yóò ma sọ fún ọkàn mi pé, *Sé nkan tí ò ńse yí sì dá ọ lójú?*

Mó mọ̀ pé Ẹ̀mí Mímọ́ yóò sọ fún ọ iye owó nà tí o bá bi léèrè; kàn ri dájú pé o fẹ́ gbọ́ láti ẹnu rẹ̀ nítòtọ́.

Mo ti nílò ìrànwọ́ ní àrín yí ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Nítorí mo má ńsan àwọn owó tí a bá jẹ, ó rọrùn fún Drenda láti gbọ́ iye owó tí ó yẹ kí á fúnrúgbìn a kò sì ní láti sọ pé bẹ́ kọ̀. Sé o rántí ìtàn tí mo sọ fún ọ nípa ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ́ùn sí ọgbà ilé ẹ̀kọ́ wa ti Faith Life fún ìgbà àkọ́kọ́?

O da, Mi ò tilẹ̀ sọ gbogbo ohun tí ó wà nídi ìtàn na. Ó jẹ ohun tí yó gbà wá bí ọdún mẹ́ta, kì ise gbèsè bíkòse àfojúsùn tí a ti lá kalẹ̀ fún ara wa fún àwọn àkókó kan.

Nígbàti ọjọ́ nà dé tí aní láti fi nkan tí a fẹ́ se hàn àti kí a gbín èso tí a fẹ́ fúnrúgbìn, Mo ti lérò pé ọ̀kẹ́ mèje àbọ̀ pọ́ùn ni mo fẹ́ kí a fi sílẹ̀. Sùgbọ́n Drenda jíyàn pẹ̀lụ́ mi pé ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ̀ùn ni òuń gbọ́. Mo dá oun tim ó ńsọ nù mo dúró lórí ẹsè mi pé ọ̀kẹ́ mèje àbọ̀ pọ́ùn ni. Nínú ìse bẹ́ẹ̀ni ó sì sọ pé ànísẹ́ ọ̀kẹ—Mẹ́wa pọ̀ùn ni a ó fi sílẹ̀, síbẹ̀ èmi na kọ̀jálẹ̀. Ní ibiti a wà tí a fẹ́ ti fi èso wa sílẹ̀ ní ọjọ́ nà gàn, àgbẹ̀ kan láti inú ìjọ mí dìde wọn ní kí ó sọ̀rọ̀. Ó gba gbogbo èniyàn níyànjú láti fi ìgbékèlé wa sínú Ọlọ́run fún ìkórè wọn. Ó sì tẹsíwájú láti sàlàyé pé gẹ́gẹ́ bí àgbè àwọn má fi ọkàn wọn sínú òfin gbíngbín àti kíká láti gbé àti rípé ó tó gbẹ́kẹ̀lé. Óní òun nà ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ̀ùn ní ọdọdún láti fún irúgbìn èso. Ó tún wà ní, níbẹ̀rẹ̀ o le dàbí ọ̀rọ̀ wèrè láti da ọ̀kẹ́-mẹ́wa sínú ìdọ̀tí nítorí o fẹ́ fún irúgbìn èso lẹ́kan, kò sí ọ̀nà tí wà fi rí gbà padà. Sùgbọn ó wà tẹnumọ òfin gbìngbìn àti kíká pé ni ó má borí pẹ̀lú ìkórè tí o tún tóbi ju ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ̀ùn ti o ná lórí oko nà lọ.

Drenda rọra fọwọ́ tọ́ mi lẹ́gbẹ. Mo gbàa—ọ̀kẹ́-mẹ́wa poùn na ni a sì fúnrúgbìn. Ó sì rántí bi Ọlọ́run ti se lo igbákejì Aàrẹ láti máa fún wa ní ẹ̀bun ní ọdọdún ní ọdún nà- tí ó sì jẹ́ ọ̀kẹ́-mẹ́wa pọ̀ùn. Kò ná wá ní kóbò láti fúnrúgbìn èso na rárá. Àtípe bí mo ti sọ nínú ìpín nà sáájú, pé ẹ̀bùn náà wà fún ọ̀pọ̀ ọdún ni tí wọn sìsan owó tí ó lé ní Miliọ́nù méjì pọ̀ùn bí owó tí ńwolé fún wa.

Sé o rí, ọkàn Drenda kò kún fún ọ̀pọ̀ àwọn nkan bí èyí tí èmi ńse kò ní fi àyè sílẹ̀ fún ìbẹ̀rù pé o tún fẹ́ dìde ní tàbi ǹkan mí Òn má ńgbọ́ ohùn

Ọlọ́run. Àtí pem lótítọ́ nkan tí èmi na nílò láti se nìyí. Sùgbọ́n ìgbà àkókó nìyí tí a fi owó tí o tó bẹ̀ fuńrúgbìn, Mo fí ìfi fún ni sínú ẹ̀rù nígbàti mo nim ọ̀kẹ́- méje- àbò pọ̀ùn ni. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún ìyàwó mi, tí ó gbàmíníyànjú láti gbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run fún iye owó tí ó tún pọ̀.

*Gbogbo ìgbà* ni mo má ńlo ìgbàgbọ láti fúnrúgbìn, *gbogbo ìgbà.* Torinà ẹ má jẹ́ kí a gba ìbẹ̀rù kí o dá wa dúró láti le kórè gbogbo ohun tí Ọlọ́run ńgbìyànjú láti fi fún wạ.

> *Máa se ìrántí ẹsẹ̀ yìí:Ẹní tí ó bá fúnrúgbìn kín ún, kín ún ni yóò ká; ẹni tí ó bá sì fúnrúgbìn púpọ̀, púpọ̀ ni yóò ká.*
>
> —2 Kọ́ríntì 9:6

Nínú ẹ̀kọ́ yí Páùlù ńgba ọrẹ fún àwọn ìjọ míràn, ó wá ńran àwọn ènìyàn létí òfin bóyá èyí tí ó ti kọ́ wọn sáájú, pé ohun tí wọn bá gbìn ni wọn yóò ká gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n tí wọ́n bá fi wọ̀n. Páùlù bẹ̀rẹ̀ sí sọ òfin ti ètò òsùnwọ̀n.

Nígbàti Pétérù gbé ọkọ̀–ojú-omi rẹ̀ fún Jésù láti lò ní etí odò, a rí wípé àti Jákọ̀bù àti Jòhànù ni ọkọ̀ ti wọn nà kún fún ọ̀pọ̀ ìkórè tí Pétérù lò ìgbàgbọ́ rẹ̀ fún nítori tí wọ́n jẹ́ alábasisẹ́pọ̀. Sùgbọ́n jẹ́ kí nbi ọ lérè ìbéèrè yí: Tí o bá jẹ́ pé Pétérù wà lọ ní bí ẹgbẹ̀rún kan ọkọ̀-ojú-omi ní ọjọ́ nà ńkọ́ fún isẹ́ rẹ̀, ọkọ̀ ojú omi mélòó ni yóò wá kún?

Tí o bá sọ pé ẹgbẹ̀rún kan na ni ò tọ́ lo sọ.

Lẹ́ẹ̀kansi, a rí òsùnwọ̀n tí ó ti sètò kalẹ̀. Òsùnwọ̀n tí a fi fún wa ni *bí agolo* tí Ọlọ́run le kó ńkan kún inú rẹ̀. Torínà, mo gbà ọ́ níyànjú láti seo òsùnwọ̀n rẹ pẹ̀lú ìran ńlá. O kò ní fẹ́ lọ wẹ̀yìn wò àti sọ pé, Wow, ọjà tún ti lọ sókè ni ìdálọ́nà ẹgbẹ̀rún láàrin wákàtí mẹ́ta. Mi ò bá mọ̀ kin ti se jù bẹ lọ."

Ohun tí ó mú mi fi ọ̀kẹ́ -méje -àbọ̀ pọ̀ùn si ní alẹ́ ọjọ́ nà lẹ́yìn tí Ẹ̀mí mímọ́ ti sọ fún mi láti lo ra ọjà? Ó dára, ní tèmi, ohnu tí ó fa ni pé èmi ò bèèrè lọ́wọ́ Ọlọ́run pé kí ó sọ iye tí ma rà fún mi. Mo kàn ńse ohun tí ọkàn mi fẹ́, mo sì pàdánu ohun Rẹ̀.

Ní báyìí, jọ̀wọ́ má jáde lọ ra ọjà ńlá nítorí ìtàn tó ǹká yìí. Gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ sáajú, èmi ò fi owó tó pọ̀ sí ọjà na. Sùgbọ́n Ọlọ́run se nkan tí ó fẹ́ se ní alẹ́ ọjọ́ nà—Ọlọ́run tí ń fi irúgbìn fún afúnrúgbìn, àti àkàrà fún oúnjẹ ó sì

jẹ́ ohun tí o ránnilétí láti sètò òsùnwọ̀n *wa*.

Mo lérò pé wa sì ránti ìtàn yí nígbà míràn tí Ọlọ́run bá fọwọ́ tọ́ ọ léjìká fún isé Rẹ̀ láti se.

Àní láti gba Ọlọ́run lááyè láti kọ́ wa lórí ǹkan yìí.

Mo sì tún le rántí ìgbàtí ǹkan wálẹ̀ lórí ohun ìní ní Florida ní ọdún 2009 tí nkan dàrú. Aní àwọn ọ̀rẹ́ níbẹ̀ tí wọ́n ńgbe etí òkun, tí a sì ma ńse àbẹ̀wò sí wọn lóòrekóòrè. Ní àsìkò na, ọ̀pọ̀ ilé ni ó wà fún títà ní gbogbo Florida. Bí a tí nkọjá lọ létí òkun pẹ̀lú ọ̀rẹ́ wa ní ọjọ́ kan, ó ní "Mo fẹ́ fi nkan hàn yín."

A wá lọ sí ibi ilé kan tí wọ́n kọ àkọlé sí fún títà si lára. Iye owó tí wọ́n kọ sì ni ẹgbẹ̀rún ní àrún dín *ní* ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ́rin owó pọ̀ùn fún ilé méjéjì tí ó wà lórí ohun ìnim nà. (Bẹ́ẹ̀ni o ri kà dada, ilé méjèjì ní etí òkun fún rún dín *ní* ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ́rin ẹgbèrún. Wọn yóò tún tí se lọ́sọ bamkanna. Mo lérò pé àwa méjèjì yóò gbà pé olè jíjà lèyí.) Tí o bá yá wọn lọ́kan lò, yóò ma mú owó ńlá wọlé wá ní nitorí àwọn ilé yì wà ní etí òkun. Súgbọ́n mi ò fẹ́ ná irú owó bẹ̀ ní àkókò na, mo sì kọ̀ láti rà wọ́n. (Mo mọ̀, Mo mọ̀ pé mi ò yárató.) Ọ̀rẹ́ mi ní àwọ́n ilé nílè kò sì fẹ́ ní ilé pípọ̀ lọ́wọ́ ní àsìkò na. Mo ní ó mú wa lọ síbẹ̀. Kì íse ojojúmọ́ ni àwọn olówó má gbà ọ́ nímọ̀ràn bẹ "pé nkan tí mi ò bá se nìyí." Bẹ́ẹ̀ni, Drenda nsọ pem kí a ra, sùgbọ́n mi ò dáhùn.

Sé o wá ri , o le sọ ohnu tí ó le sẹlẹ̀. Ilé méjèjì yí ni wọ́n tà ní ọdún díẹ̀ sí ìgbàna ní Milliọ́nù mẹ́ta pọ̀ùn.

**TORIBẸ, MÁ JẸ́ KÍ ERÙ BÀ Ọ́ SỌ́RỌ̀ NÍGBÀTÍ O BÁ ŃFÚNRÚGBÌN ÀTI SÈTÒ ÒSÙNWỌ̀N RẸ. NÍ ÌGBOYÀ.**

Sé o wá ri ohun tí ó dùn ni jùlọ níbẹ̀ nipé? Mi ò tilẹ̀ gbàdúrà lóri rẹ̀ ní ọjọ nà .Mo gbé ọgbọ́n ti Èmí Mímọ́ sí ègbẹ́ kan. Mo sàìkọbi ara sí ọgbọ́n ọ̀rẹ́ mi àti ti ìyàwó mi tí ó gbọ́n gan. Mo tún sọ pé rárá nítorí mo mò pé gbogbo owó tí a ní ní yóò gbà tán ní àsìkò na, àti bí ètò ọrọ̀ ajẹ́ se ńlọ sókè, mo kàn ri wípé kò wù mí láti seé ni. Sùgbọ́n bí mo ti sọ, mi ò bérè lọ́wọ́ Ọlọ́run nípa rẹ̀ tí ò sì jẹ́ àsìse ńlá fún mi.

Bẹ ọ̀pọ̀ àwọn ìkórè ni mo ti pàdánù (Kì iśe gbogbo rẹ̀ sùgbọ́n ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀), Tí Ọlọ́run sì ní láti bámi wí pẹ̀lú rẹ̀.

Ní ọjọ́ kan bí ọdún kan sẹ́yìn, Drenda sàdéédé bá Kenneth Copeland

pàdé nígbàtim ó wà nim ìsinmi ránpẹ́, ó sì pé láti wá bá òun àti ìyàwó rẹ̀ Gloria jẹ óunjẹ òwúrọ̀.

Ní orí tábílì tí wọ́n tí njẹun Kenneth sọ pé óun ní ọ̀rọ̀ fún Drenda àti èmi. Ó sì ká ohùn náà sílẹ̀ lórí fonù rẹ̀ fún mi nítorí tí mi ò sí pèlú rẹ̀ ní àsìkò na, ọ̀rọ̀ na si lọ báyìí:

> "Mo ti gbìyànjú àti fún ọ ní àwọn ilẹ̀ àti àwọn ilé, sùgbọ́n o kò gbà mí láàyè láti sé."

Wow, ìbániwí nìyìí. Sùgbọ́n bí mo ńrò ọ̀pọ̀ ohun tí ó ti sẹlẹ̀ sẹ́yìn tí mo ti sọ pé rárá fún, mo wá rí àwọn àsìse mi. Torinà, Mo wá pinu ní ọkàn mi láti ìgbàna lọ pé mi ò ní pàdánù àwọn ìkórè mi mọ́ láí. Ní kété tí mo bá ti se pìnnu. Ó ma njẹ́ ohun ìyàlẹ́nu bí Ọlọ́run ti se máa nyára má ńmú àwọn nkan na tí a ti fúnrúgbìn fún wá.

Toribẹ, má jẹ́ kí ẹ̀rù bà ọ sọ̀rọ̀ nígbàtí o bá fumnrumgìn àti sètò òsùnwọ̀n rẹ. Ni Ìgboyà. O kò ní mọ̀ bí Ọlọ́run yóò ti se mú àwọn ohun ná wá sí ìmúsẹ, gẹ́gẹ́ bí obìnrin opó nì nínú ìwé 2 Àwọn Ọba 4 kò se lérò pé òromró na yóò kàn máa sàn lọ ni. Tí o bá mọ̀ ni, Ìtàn rẹ̀ kò bá tún yàtọ̀ pátápátá. Bóyá à bá sì tún má kà ńipa obínrin opó tí ó ti di billiónìa nínú isẹ́ òróró títà lónìí.

Ní ìparí, rántí pé gbogbo ìgbà ni wà má fúnrúgbìn sínú ìkórè ńlá. O wà láyè lónìí láti inú ìkórè ti àná, wà si fi èyí sọkàn nígbàtí o bá tún fúnrúgbìn.

Bákanna, rántí pé ìgbà òkùnkùn ni lẹ́yìn tí o bá ti fúnrúgbìn. Ìgbà irúgbìn na dà bí pé òfo ni ti èso kò tí bẹ̀rẹ̀ sí ní hù jáde. Sùgbọ́n dúró nínú Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, dúro tirii, kí o sì ma gbàdúrà nínú Ẹ̀mí fún ìtọ́ni àti bí niti gbogbo ìkórè ti Ọlọ́run ńmú bọ̀ wá fún ọ.

Mo parí ìpín yìí pẹ̀lụ ìtàn tí mo ti sọ ní ọ̀pọ̀ ìgbà tí ó sì tún jẹri gbe ara rẹ̀. Ó ní se pẹlú àlágbàtà mi kan, bí ọdún díẹ̀ sẹ́yìn, nígbàtí mo sẹ̀sẹ̀ ńkọ́ ẹ̀kọ́ nípa òfin bí a tí nsètò òsùnwọ̀n. Ó ńkọ́ ilé titun kan àti bí gbogbo àwọn ilé titun tí wọ́n ńkọ tiyẹ kó se, wọ́n tún lọ sàtúnyẹ̀wò ìsúná wọn wò. Àwọn nkan tí ó yípadà tàbí iye owo tí wọn o fi kún ohun tí o ti yípadà.

Ó da, ní àsìkò yí ọ̀rẹ́ mí ti ná gbogbo owó ti bánkì fún láti lò, ó wá yo sílẹ̀. Tí mo bá rántí ọ̀rọ̀ na, Kò sí ní owó tí o ma fi ra ohun èlò ti yàrá ìdáná.

Mo rò pé owó nà yó tó ẹgbẹ̀rún mẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n pọ́ùn.

Ní alẹ ọjó kan, òkan lára àwọn asojú isẹ́ àti èyí tí ó nkọ ilé jọ lọ sí ibi ìjọ́sìn kan. Nígbàtí wọ́n fẹ́ parí ọ̀rọ̀ ìfiránsé, oníwàásù wá sọ pé mú ọrẹ re wá fún ìdíkan, mí ò tún mọ ohun tí ó tún sẹlẹ̀ mọ́, sùgbon alágbàtà ọjà mí tí ó tẹ̀lé ẹkejì rẹ̀ lọ, èyí tí ó ńkọ̀lé lọ́wọ́ wa bámí óní ó dàbí pé ẹnití ó nkọ̀lé lọ́wọ́ yí ní àwọn nkan tí ó ńdojúkọ lọ́wọ́ ní alẹ́ ọjó nà.

Ó sàlàyé fún mi pé èyí tí ó ńkọ̀lé lọ́wọ́ lọ fi ọrẹ rè sílè níwájú ó padà wá jókóò ní àyè rẹ. Ó ní ó dàbí pé nkan ru sókè nínú rẹ̀. Ó wá sọ fún mi pé o tún dìdè ó sì tún lọ síwájú ó sì tún lọ fi owó míràn sílẹ̀. Ní gbàtí ó tún ńpadà bọ sí àyè rẹ, ó ní nkan tí ó tún rò, ó jókòó bí ìséjú kan o tún dìde, pẹ̀lú ìrora, ó tún kọjá sí iwájú ó tún lọ fi owó míràn sílẹ̀. Nígbàtí ó wá padà dé, ó wá ní Àlááfíà kò sì sí nkankan tí o seé mọ́.

Nígbàti ó yá nínú osù na, ẹnití ó nkọlé lọ́wọ́ nà wá jẹ́ ẹ̀rí pé òun fúnrúgbìn ní alé ọjọ́ nà nínun ìjọ fún owo tí òun nílò láti parí kábínẹ́tì yàrá ìdáná tí òun ti san owó fún. Tí mo bá rántí dáda, ẹniti ó ńkọ ilẹ̀ nà pínu láti dín owo rẹ̀ pẹ̀lú ìdáméjì owo nà, ó sì palẹ̀ àwọn oko owo kan mọ́ láti le san owo nà.

Torinà, kín ni ohun tí ó ńsẹlẹ̀ ní alẹ́ ọjó nà? Ẹni tí ó nkọ́lé ní ọjọ́ na sọ wípé níse ni ara òun kò balẹ̀ títí ó fi di ìgbà kẹta tí òun lọ láti lọ fi gbogbo ohun tí òun ní sílẹ̀. Ó sì ti ńgbàdúrà lórí bí yóò ti se rí ẹgbẹrún mẹ́ẹ̀dọ̀gbọ̀n pọ́ùn san, Ẹ̀mímímọ wá darí rẹ̀ láti sètò òsùnwọ̀n tí ó nílò láti le mú ìkórè tí ó ńfojúsí wá fún un.

Toríbẹ̀, ma rántí òfin Ìjọba ó se pàtàkì, òfin òsùnwọn, nígbà míràn tí o bá nfúnrúgbìn rẹ.

ORÍ KẸWÁ

# ỌBA ONÍNÚRERE

Mo mọ̀ dájú pé gbogbo wa ni ó ti se bẹ ri. Ẹnìkan kán wá ó wá kí wa, ó wá sọ ọ̀rọ̀ kan báyi pé. “Oh, mo ra kinní yi wá láti gáréèjì ní Pọ̀ùn máàrún.”

Kílódé tí a fi máa sọ ǹkan báyìí” Kílódé tí ojú fi máa tì wá láti ní ohun tódára? Ó jẹ́ ǹkan tó dára tí ó sì banilọ́kànjẹ́ pé nígbàti à ńkọ́lé ilé wa titun ní ìlú wa ní bí ogún ọdún sẹ́yìn, a gbàdúrà pé yóò tóbi nínú sùgbọ́n kéré ní ìta bí a bá ńwo. Pásítọ̀ titun ni a jẹ́, a sì wòó wípé àwọn ènìyàn le ma bínú tí a bá ńkọ́ ilé tí ó tóbi. Ní àsìkò tí a ńsọ yí a kò sì gba owó kankan lọ́wọ́ ìjọ—owó tí a ná láti kọ́ ilé nà wá láti inú oko-òwò wa—sùgbọ́n fún ìdí kan, a rò wípé àwọn ènìyàn yóò maa rò wípé owó ìjọ ni a ná fi kọ́lé. Toríbẹ a wá kọ́lé o ní ìwọn ẹsẹ̀ bàtà 7,700 sórí ilẹ̀, tí a bá wá wo ilẹ̀ na yóò wá dàbí ilé alájà méjì.

Nígbàtí ó wá yá a wá rí bí nkan tí kò bójúmu. Kílódé tí a fi gbọ̀dọ̀ ma tijú àwọn ìbùkún Olúwa?

Mo lo àkàwé yí ní àwọn ìpàdé àpérò tí mo se.

Ó da, kí a wòó pé níse ni, mo rákòrò wá sí orí pẹpẹ yìí tí mo tún wá wọ asọ èkísà tí mo wá ńsọ pé òní ni ọjọ́ àjọyò; Èmi àti Drenda ti san gbogbo owó ilé wa tán. Mo wá bèrè sí ní sọ bí a ti sisẹ́ tí ó lágbára (nígbàmíràn a mọ se isẹ́ tó ọgọ́rin wákàtí ní ọ̀sẹ̀) kí a le ri se.

Gbogbo ènìyàn ni wọn ó pàtẹ́wọ́ wọn o sì pariwo. Kínni ìdí? Nítorí tí ẹnìkan ti se bí wọ́n tí máa ńse. Bí wọ́n ti rí nìyẹn.

Sùgbọ́n tí mo bá wá sí orí pẹpẹ tí mo sọ pé, “Lónìí, àlejò kan kàn wá bámi ó sìgbé Milliọ́nù kan pọ́ùn lé mi lọ́wọ́, a sì ti san gbogbo owó ilé wa tán”

Gbogbo wọn yóò sọ pé kò dára bẹ́ẹ̀ tó o. Kílódé? Nítori bí a ti ati se

kọ́ wa níti ètò ti ègún pé nínú ìrora àti òógùn ojú rẹ. Bí a ti fi kọ́ wa nìyí láti má kọ ọ̀rọ̀ wa jọ nìyìí. *Lóòtọ́,ì*múnilẹ́rú ni, bí ọ̀pọ̀ kò ti se gbádùn òmìnira kankan nínú ìsúná wọn nìyí. Torí ìdí èyí, ọ̀pọ̀ ni kò tí sàwárí èrèdí wọ́n, àti mọ DNA tẹ̀mí wọn. Nítorí irú ìgbésí ayé tí wọn ńgbé, ìpinnu wọn sì dá lé orí *owó* tí wọ́n rí ní àyíká wọn, kìse *èrèdí.* Àwọn ènìyàn má fojúsí láti di òmìnira láti le mú kí ìran àti ìfẹ́ wọn wá sí ìmúsẹ, sùgbọ́n fún ọ̀pọ̀, kò rí bẹ̀.

Ní bí ọdún díẹ̀ sẹ́yìn, Ọlọ́run bẹ̀rẹ̀ sí ní kọ́ mi nípa ìlópo méjì àti bí o ti jẹ́ ti wa. Ìlọ́po méjì ni ó sọ wá di òmìnira kúrò nínú ègún tí a fi ayé gún níti ìnira àti òógùn ojú wa kí á tó gbáyé tó rọrùn.

Ní kúkúrú, ìlópo méjì túmọ̀ sí, *ó tó ó tún sẹ̀kù.* Tí o ba ní ànító àti ànísẹ̀kù wa gbé laí jẹ gbèsè kankan àti má se isẹ́ wa, dípò títa ayé wa kiri nítori owó.

Bíotilẹ̀jẹ́wípé mo ti ńsọ̀rọ̀ nípa ìlọ́po méjì nínú àwọn ìpàdé àpérò mí fún ọ̀pọ̀ ọdún, Mo rò pé Olúwa fẹ́ fi nkan hàn mí nípa rẹ̀ tí kò ti yé mi dáadáa. Mo mọ̀ pé ó poð ju nkan tí mo ńrí lọ, mo sì bí Ẹ̀mi Mímọ́ láti fihàn mí nkan nà tí ó jẹ́.

Mo wá bẹ̀rẹ̀ sí ní kà àti sàsàrò nínú Ìwé Mímọ́ nípa ìlọ́po méjì àti dúró de Olúwa láti fi ohun tí mi ò ti rí hàn mi. Ó da, mo wá fura sí àwọn àfihàn àwọn nkan tí ó fẹ́ jẹ́ kín mọ̀ tí mi ò tilẹ̀ le lérò rẹ̀ láí.

Mo gba ìpè láti ọ̀do arákùnrin kan tí mi ò tí bá pàdé rí, ọ̀kan lára àwọn alábásisẹ́pọ̀ ni ilé isẹ́ ìránsẹ́ wa ni. Lẹ́yìn ìgbàtí ó ka àwọn ìwé mi, ó ri pé mo fẹ́ràn láti máa sọdẹ, ó wa pè ó sọ pé, "mo fẹ́ láti ra ìbọnkúkúrú kan fún ọ. Irú èwo ni o kò ti nị?"

Nígbàti a ńsọ yìí, orísi àwọn ìbọn ni mo ní tí mo má ńlò láti sọdẹ bí àgbọ̀nrín, pẹ́pẹ́yẹ, àparò, àti ehoro. Kódà Mo tún ní Sakabùlà tí ò ma ńgba ogún ọta sínú èyití bàbá mi rà fún mi nígbàtí mo wà ní ọmọ ọdún mẹ́rìndínlógún. Sùgbọ́n gbogbo ìgbà ní inú mi máa dùn tí mo bá rí ìbọnkúkúrú tí ó dára mo ti ri ní ọ̀pọ̀ ìgbà nínú àwọn ìwé ìròyìn tí ọdẹ síse. Wọ́n ma ní àwọn èyi tí wọ́n fí isẹ́ ọnọ̀ se ọ̀pá wọn tí wọn sì máa dúró dáda ní pípé. Toribẹ, mo wá sọ fún pé mi ò ní ọ̀kankan tí mo ńrò báyi lọ́wọ́lọ́wọ́. Ó yàmílẹ́nu nígbàtí ó sọ pé òun yó fí ọ̀kan ránsẹ́ sími.

Nkan tí ó dájú ni, inú mi dùn bí ó ti sọ bẹ.Sí ìdánilójú, ọ̀sẹ̀ kan sí ìgbàna, wọn fi àpótí kan ransẹ́ sí ófísi ìjọ mi, bí mo ti síyẹ̀wò kòsí nkan

míràn bíkòse àwọn ìbọn kúkúrú *méjì* tí ó rẹwà tí mi ò ti rí rí lọ.

Mo yára pe alábásisẹ́pọ̀ mi na mo sì dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ̀ fún ẹ̀bùn tí ó dára na.

Ní ọ̀sẹ̀ tí ó tèle, ó tún fi méjì míì ránsẹ́ sí mi! Ó wá jẹ́ ìbọn mẹ́rin tí ó dára jùlọ tí mo ti ní. Mo tún pe ó sì ti má ńsọ nígbogbo ìgbà pé àwọn ènìyàn kì pe òun láti dúpẹ́ fún àwọn ẹ̀bùn tí ó bá fún wọn; sùgbon nítorí tí mo se bẹ ní òun se tún fi mejì míràn ránsẹ. Kedere ní ó hàn si mi pe nkan tí Ọlọ́run fẹ́ se nìyìí. Méjì ni ó wá lẹ́kànna, ní méjì méjì, mo sì ti ń bi Ọlọ́run léèrè nípa ìlọ́po méjì.

Ó da, láti sọ ní kúkúrú èdè, ìbọn bẹ̀rẹ̀ sí ní wọlé wá, ní méjì méjì. Kí ó tó pé bóyá mo ti ní tó ìbọn kúkurú MẸ̀RÌNLÁ titun, tí wọn sì jẹ́ àwọn gidi tí ó dára. Àwọn ìbọn wọ̀nyí kì ìse olówó kékeré. Owó àwọn ìbọn na yó tó ẹgbẹgbẹ̀rún owó dọ́llàr.

Mo sì ní ọkọ̀ funfun méjì Cadilac Escalade SUV tí wọn fún mi .Ní àsìkò na, a sí ńwa ọkọ̀ wa Honda Pilot tí ó ti pé bí ọdún mẹwà tí a ti ńwa ọkọ̀ na, a fẹ́ràn ọkọ̀ na (torí àwọn ọkọ̀ Honda má dára gan ni), sùgbọ́n wọ́n kì íse Escalades.

Louis Vuitton purse ni ọkọ̀ tí Drenda fẹ́ràn fún bí ọdụn díẹ̀ sígbàyí, mo sì fun ní ọ̀kan bí ẹ̀bùn ọdún kérésìmesì ní ọdún melo sẹ́yìn Súgbọ́n fumn ọjọ́ ìbi rẹ̀ nínú ọdún yi, ó rí—kínni gbà—sọm—Louis Vuitton purses MÉJÌ ọ̀tọ̀tọ̀ gbà, àwọn ènìyàn méjì ọ̀tọ̀tọ̀ ni ó fún un.

Ọkọ̀ òfurufú wa kejì tún farahàn ní àsìkò yí gan, bákanna, ilé méjì létí òkun tún jáde wá, léked gbogbo rẹ̀, ní ìgbà kérésìmesì wọ́n fún wa ní àwọ̀lékè onírun méjì tí ẹyọkọ̀kan tó ọ̀kẹ́ máàrún pọ́ùn.

Jẹ́ kín dúró kín se alàyé fún ọ pé kì íse pé mo ńse ìgbéraga ni, nítorí èmi kò se bẹ!!!! Ìbọn méjèjì kàn wá ni. Ọkọ̀ Escalades méjí kàn wá na ni. Ọkọ̀ purses na wá ni. Àwọ̀lékè onírun na sì wá bẹ̀.

Ilé méjéjì, bẹ́ẹ̀ni na wà níbẹ̀, sùgbọ́n àwa na ti fúnrúgbìn fún ilé létí òkun bí ọdún díè sáájú. Èmi ò mọ̀ kò sì sọ fún mi nígbànà, sùgbọ́n yìn ọdún díẹ̀, Drenda rí ilé tí ó fẹ́ràn nínú ìwé ìròyìn tí àwọn akólétà. Ó rántí pé òun sọ pé “Olúwa, mo fẹ́ èyí,” Ní ìgbàtí à ńsọ yim ọ̀pọ̀ isẹ́ lọ wà tí a fẹ́ fowó se tí a sì wo owó tí ó wà láti yanjú ilé ti Florida, sùgbọn a mọ̀ pé ọkàn yóò yọjú n*í* àkókò rẹ̀.

Ní ọjọ́ kan bí mó tí ńsáré láìyára, Olúwa bámi sọ̀rọ̀ ó sọ pé, “ *Rán*

*Drenda lọ sí Florida láti lọ ra ilé rẹ̀* "Ni kíakía ní ìyára tí wá pẹ̀lú lílọ rẹ̀ ní ọ̀la, mo sọ pé, Wow. Ó dá mo ti gbọ́, Olúwa."

Toríbẹ, Drenda lọ sí Florida ó sì lọ wo àwọn ilé mẹ́ẹ̀dógbọ̀n ọ̀tọ̀tọ̀. Lára àwọn ilé tí ó wò na, ọ̀kan sí wá sí ọkàn rẹ̀ pé ilé nà ni ó wà fun.

Mo lọ sí Florida láti lọ bá wòó a sì jọ gbà pé ó dára. (Nígbogbo ìgbà yìí ó ti gbàgbé nípa ọjọ́ tí ó nawọ́ sí ilé nà nínú ìwé ìroyin àwọn akọ́létà tí ó sì sọ pé òun ni yóò ni ilé nà. Ó tó bí ọdún mẹta sí ìgbàna àwa gan kò sì tí rí ilé nà rí).

A sàdéhùn lórí ilé tí ó fé; ní ọjó kan bí ati se jókòó ní ilem wa ní Ohio tí à ńsisẹ́ lórí àwọn isẹ́ kan tí o nílò àyẹ̀wò ati àlàyé, Drenda kan pariwo nipé "Ilé mi nì yìí!"

Mo rò wò nìwọ̀n ìgbàtí a wà lórí àdehùn àti pé a mú ohungbogbo wà sí ìparí. Lóòtọ́ ilé rẹ̀ ni, nkan tí mo sọ.

"Ó le ma ye ọ," ó sọ pé. "*ilé yi gan* ni mo tọ́kasí nínú ìwem ìròyìn àwọn akọ́létà ní bí ọdún melo sẹ́yìn!"

Nígbàna ni mo wá rántí ìwé ìròyìn na tí ó ńsọ tí o nwò ní bí ọdún mẹta sẹ́yìn tí o rí ní ilú yi kanna. Se ó le jẹ́ ilé yí kanna? Drenda mọ̀ dájum pé ilé yí kanna ni, ó wá bẹ̀rẹ̀ sí ní sọ àwọn nkan tí ó rí ní ara ilé nà lọ́jọ́ nà lọhun. Tí ò sì wá jẹ́ bákanna lórí lára ilé nà. Mo wá lo se àwọn ìwádi kan, lóòtítọ́, ilé tí a fẹ́rà na wà lára èyí ti wọ́n kọ jáde lọ́dún nà ní ìgbàtí Drenda rí tí ó sì tọka si àti sọ ọ́ jáde pé òun ni yóò ra ilé nà. Sùgbọ́n ní ìgbàna, fún àwọn ìdi kan, lẹ́yìn ìgbàtí om ti sọ pé ti òun ni, wọn ti gbé kúrò lóri igbá.

Bí mo ti wá nka ìtàn ilé nà, mo wá ri pé ó ti kúrò lomri àtẹ nigbogbo ìgbàyí wá tí o fi wá di bí ọjọ́ melo tí wọ́n tún wá dapadà sórí àtẹ ọjà. Abálájọ tí Ẹ̀mí Mímọ́ fi sọ wípé rán lọ sí Florida ní ọ̀la!

Toribẹ, a ra ilé etí òkun na, Drenda wá di ẹnití ó ní ilé nà, nkan tí ó ti lála rè ní ọjọ́ tó pẹ́. Bẹ́ẹ̀ni a tún jogún ilé etí òkun kejì ní Canada ní ọdún yìí gan na. Wow!

Tí o kò bá ti kíyèsi, ohungbogbo tí Ọlọ́run fi ránsẹ́ sí wa jẹ́ ohun tí ó dára; Mo ní tí ó jojú ní gbèsè. Kó dà gbogbo rẹ̀ ó dáyàjá wa díẹ̀ pé kínni ǹkan tí ó nsẹlẹ̀. Sùgbọ́n Olúwa bá mi sọ̀rọ̀ ó sọ pé "*Mo mọ̀ pé o kò ŃILÒ ìbọn kúkurú mẹrìnlá. Mo mọ̀ pé o kò nílò ọkọ̀ funfun Escalades méjì...*" Ó sì dárúkọ gbogbo nkan tí ó se fún wa.

Nígbadna ni ò wá sọ pé, "*Mí ò fẹ́ kí àwọn ọmọ Mí ní ìmòohun àìní.*

*Àwọn ni ó ni gbogbo ilẹ̀ nà, ìfẹ inú rere Mí sí ni láti fún àwọn ọmọ Mi ní ohun tó dára."*

**Ó MÚ MI RÁNTÍ PÉ ÒUN NI ỌLỌ́RUN TÍ Ó TÓ TÓ TÚN SẸ́KÙ, ỌLỌ́RUN ÌLỌ́PO MÉJÌ.**

Ó mú mi rántí pé Òn ni Ọlọmrun ànító àti ànísẹ́kù Ọlọ́run tí ó ju ohungbogbo lọ, Ọlọ́run ìlópo mẹ́jì. Ó tún tẹ̀síwájú pé Ò ní àwọn ènìyàn mí kò ronú ohun títóbi tó, wọn kò lááłá nkan tí ó tóbi tó, wọn sì ńdín ǹkan tí Òn fẹ́ sé fún woṇ kù.

Èmi ati Drenda wá ròó wò pẹ̀lú ohnu gbogbo tí Ọlọ́run tún fihàn wá. A wá ri pé a nílò láti sọ fún àwọn ènìyàn nípa ìlọ́po méjì. Ìlọ́po méjì kò túmọ̀ sí pé gbogbo nkan gbọdọ̀ jẹ́ méjìméji—Olúwa ńlo kin ba le fiyèsí Òn ni. Ìlọ́po méjì túmọ̀ *sí kí ótó kí ó sì tún sẹ́kù.*

Ọlọrun wá sọ fún mi nígbàna pé mo ni láti kọ́ àwọn ìjo mí ní èyi, mo sì gbọdò sọ ohungbogbo tí o fún wa àti bí a ti rí wọn gbà.

Bayii Drenda àti Èmi nfi àwọn nkan tí a ní pamọ́, nítorim gbogbo nkan wọ̀n yí kò ní àyè, a kò sì fẹ́ má tẹnumọ lóri pé aní nkan tàbi sọ àwọn nkan yí di ohun tí à ńwá kiri.

Sùgbọ́n àwọn kò wá àwọn nkan wọ̀nyií; Ọlọ́run ló fi wọ́n ránsé sí wa. Àwa nse ìdánilekọ lórí ìlọ́po méjì bí ọ̀sẹ̀ mọ́kànlá báyi nínú ìjọ, mo sì ti ri ipa rẹ̀ gidi gan ninu ìsúná àwọn ènìyàn ju àwọn ìgbàti àǹkọ àwọn ẹ̀kọ́ míràn sẹ́yìn.

Sùgbọn sé o wá mọ̀? Mo tún rí àwọn kan tí wọn kúrò nínú ìjọ nítori ohun tí mo pín pẹ̀lum wọn tó bí wọn nínu. Ti wọn lérò pé mi ò nílò láti má so ọ̀rọ̀ gbogbo àwọn ìbọn tàbí Escalade méji, tàbi ilé méji léti òkun, ọkọ̀ ojú òfurufú, tàbi asọ àwọléke méji. Wọn lérò wípe mo ngbéraga ni áti sọ àsọ dùn *gbogbo* rẹ̀.

Sùgbọ́n wọ́n nsé àsìse gbogbo rẹ̀. Ọlorun nfi hàn wá pe òun tó òun sì sẹ̀kù. Ìjọba Rẹ̀ kì íse ti ò nwò bí ti ayé se rí. Ìjọba rẹ jé ìjọba tí ó jẹ́ ti ànító àti ànísẹ́kù, O sì ní inú dídún nínu títọjú àwọn ọmọ Rẹ̀.

Mo ní láti má rán àwọn ènìyàn létí pé mi ò se bẹ. Ọlọ́run sé láti mú nkan jáde ni—kì íse gbogbo ènìyàn ni ó le máa wa ọkọ̀ olówó ńlá sùgbọ̀n nitori tí kò fẹ́ kí a má dín On kù mọ́. Kò fe kí a má sọ pe rárá ninu ìwà díndín Ọlórun kù ninu ohun tí ó fẹ́ se. Ó fẹ́ kí a mọ̀ pe òun ni Ọlọ́run tí o ni

ànító ati ànísẹ́kù.

Kí a ní òye yí se pàtàkì ninu ìjíròrò  jíjẹ́ onínurere wà. O ní lati ní ohun kan tí óní iu rere sí pẹ̀lú láti se, papa jùlọ lati le jẹ́ aláànú ni gbogbo *ìgbà*. Mo mọ pe o mọ̀ pé mo farabalẹ̀, mo sì ma nkọ lati ma gba ìdójútì ninu gbogbo rere Ọlọ́run.

Ni àsìkò ojo ti o nbọ̀, pásítọ̀ agbègbè kan bi mí lére pé bóyá òun le wá sọdẹ lórí ilẹ̀ mi. Mo má ńsọ fún agbo mi ni gbogbo ìgbà pé mi o ní gba ẹnikẹ́ni láàyè láti sọdẹ lóri ilẹ̀ na títí àwọn ọmọ mi ati èmi ná bá tó pa àgbọ̀nrín wa, nigbanà ni m̀a gba àwọn èǹìyàn díẹ̀ láti wá sórí ilẹ̀ na kí ìgbà nà tó parí. Ni asìkò na gbogbo wa ti ni àgbọ̀rín wa ninu ẹ̀rọ amúkan tutu, mo wá ní kí pásítọ̀ na kó wá.

Ní ọjọ́ tí o wa gan, Mo lọ ba ni ìta lati sọ àwọn ìtọ́ni kan fún un ati ibití o gbé le duro sí sọdẹ. Mo wá ri pé ìbọn àtijọ́ ti a fi ńpa ẹyẹ nị ó ńlò, ti o kan fi ìlẹ̀kẹ̀ onídẹ sí lati fi se ojúàmì rẹ̀. Irú ibon atijo yi kò sé fi sọdẹ àgbọnrín. O ní lati súnmọ́ àgbọ̀nrin nà dada nítori wọn kò se ibọn na lati fi pa àgbọnrin. Sùgbọn, lóòtọ, o le lo wọ́n, bí èmi na ti se nigbati mo sẹ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀ isẹ́ ọdẹ síse.

Sùgbọ́n mo jókòó síbẹ̀ mọ̀ nba sọ̀rọ̀, mo wá rántí ọ̀kan ninu àwọn ìbọn ti Ọlọ́run fi ránsẹ́ símì pé ó dara gan fún ọdẹ àgbọ̀nrín. Kódà, ohun gan lokàn, mo ri pe Ẹ̀mí Mímọ́ sọ wípẹ, "*Kílódé tí o se fún Pasítọ̀ yí ní ìbọnkúkúrú tí a fí npa àgbònrín tí wọ́n fún ọ? Ìwọ tún ni àwọn ìbọn tí wọn fi nsọdẹ àgbọrín míràn, sùgbọ́n ohun kò ní ìbọn tí ó dára lati fi sọdẹ.*"

Mo sì wá fún un ní ìbọn na, inú rẹ̀ sì dùn. Ẹ̀bùn na sọ nípa rere Ọlọ́run fún un ati gbà níyànjú  sí ọdọ Ọlọ́run.

Rántí ohun tí mo sọ fún ọ nínu àwọn ìpín kan sẹ́yìn—pé àwọn owó kan tàbi àwon nkan míràn ti o wà lọ́wọm rẹ kì íse tìrẹ? Ọlọrun fi fún ọ lati le bá àìní ẹlòmíràn pàdé ni.

Mo sọ ọ̀rọ̀ na láti le sọ pé: ò ńgbé ninu Ìjọba onínurere pẹ̀lú Ọba onínurere, Sùgbọ̀n o kò le gbádùn ohun gbogbo ti Íjọba ní fún ọ tí o kò bá le gé ẹ̀mí àiní tí ó ntì ọ lati háwọ́ mọ́ ohun gbogbo tí o bá ni.

Mo mọ̀ pé o ti wo ètò kan lóri Telifisiọnù nipa ẹnikan tí o háwọ́ ti o ma kó nkan pamọ ki wọn tó wa dásí ọ̀rọ̀ rẹ̀. Ilé rẹ̀ kún fún ọ̀pọ̀ ìdọ̀tí ti kòsí ayè lati kọjá nibẹ̀.  Ní ọ̀pọ̀ ìgbà wọn yóò dá ilé nà wó lati tún kọ́ nitori ó ti wà nípò títúnse Bí ọkàn wa tí rí niyi nigbati ọkàn wa bá kún fún

ojúkòkòrò ati pé o fẹ kó ohun gbogbo pamọ́ nitori ìgbà ojo. Owó ati ohun ìní ni a gbọdọ̀ fẹ̀sọ̀ se.

O tilẹ̀ le lati se àànú nigbati ìwọ na bá ntiraka. Ọlọ́run fẹ́ ki o mọ̀ pé ní ilé rẹ ọ̀pọ̀ ohun ni ó wà nibẹ̀, Torina jẹ́ onínurere. Jíjẹ́ oninurere rẹ yóò ma mú ọ̀pọ̀ èniyan wá sínu ìjọba Ọlọ́run ati sí ọkàn wọn lati gba ojúrere Rẹ̀ ati inúrere. Rántí, pé ojúrere Ọlọ́run ni ó darí àwọn ènìyàn sí ìrònúpiwàdà.

*"Nítorí ìjọba ọ̀run dàbí ọkùnrin tí ó jẹ́ baálé kan, tí ó jíjáde lọ ní kùtùkùtù òwúrọ̀, tí ó gba àwọn alágbàṣe sínú ọgbà àjàrà rẹ̀. Òun pinnu láti san dínárì kan fún iṣẹ́ òòjọ́ kan. Lẹ́yìn èyí ó sì rán wọn lọ sínú ọgbà àjàrà rẹ*

*"Ní wákàtí kẹta ọjọ́ bí ó ti ń kọjá níwájú ilé ìgbanisíṣẹ́, ó rí díẹ̀ nínú àwọn aláìríṣẹ́ tí wọ́n dúró ní ọjà. Ó wí fún wọn pé, 'Ẹ̀yin pàápàá, ẹ lọ ṣiṣẹ́ nínú ọgbà àjàrà mi, bí ó bá sì di òpin ọjọ́, èmi yóò san iye ti ó bá yẹ fún yín.' Wọ́n sì lọ.*

*"Ó tún jáde lọ́sàn án ní nǹkan bí wákàtí kẹfà àti wákàtí kẹsànán, ó túnṣe bákan náà. Lọ́jọ́ kan náà ní wákàtí kọkànlá ọjọ́, ó tún jáde sí ààrín ìlú, ó sì rí àwọn aláìríṣẹ́ mìíràn tí wọ́n dúró. Ó bi wọ́n pé, 'Èéṣe tí ẹ̀yin kì í ṣiṣẹ́ ní gbogbo ọjọ́?' "Wọ́n sì dáhùn pé,*

*"Nítorí pé kò sí ẹni tí yóò fún wa ní iṣẹ́ ṣe."*

*"Ó tún sọ fún wọn pé, 'Ẹ̀yin náà ẹ jáde lọ ṣiṣẹ́ pẹ̀lú nínú ọgbà àjàrà mi."*

*Nígbà tí ó di àṣálẹ́, ẹni tó ni ọgbà àjàrà sọ fún aṣojú rẹ̀ pé, 'Pe àwọn òṣìṣẹ́ náà, kí ó san owó iṣẹ́ wọn fún wọn, bẹ̀rẹ̀ láti ẹni ìkẹyìn lọ sí ti ìṣáájú."*

*"Nígbà tí àwọn ti a pè ní wákàtí kọkànlá ọjọ́ dé, ẹnìkọ̀ọ̀kan gba owó dínárì kan. Nígbà tí àwọn tí a gbà ṣiṣẹ́ lákọ̀ọ́kọ́ fẹ́ gba owó tiwọn, èrò wọn ni pé àwọn yóò gba jù bẹ́ẹ̀ lọ, ṣùgbọ́n ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn gba owó dínárì kan. Bí wọ́n ti ń gbà á, wọ́n ń kùn sí onílẹ̀ náà, pé, 'Wákàtí kan péré ni àwọn tí a gbà kẹ́yìn fi ṣiṣẹ́, ìwọ sì san iye kan náà fún wọn àti àwa náà ti a fi gbogbo ọjọ́ ṣiṣẹ́ nínú oòrùn gangan.'*

*"Ṣùgbọ́n ó dá ọ̀kan nínú wọn lóhùn pé, 'Ọ̀rẹ́, kò sí aburú nínú nǹkan tí èmi ṣe sí yín. Kì í ha ṣe pé ẹ̀yin gbà láti ṣiṣẹ́ fún owó dínárì kan. Ó ní, Gba èyí tí í ṣé tìrẹ, ki ó sì máa lọ. Èmi fẹ́ láti fún ẹni ìkẹyìn gẹ́gẹ́ bí mo ti fi fún ọ. Àbí ó lòdì sí òfin pé kí èmi fún ẹnikẹ́ni ní owó mi bí mo bá yàn láti ṣe bẹ́ẹ̀? Kí ni ìdí tí ìwọ ní láti bínú nítorí èmi ṣe ohun rere?"*

"Bẹ́ẹ̀ ni àwọn ẹni ìkẹyìn yóò di ẹni ìṣáájú, ẹni ìṣáájú yóò sì di ẹni ìkẹyìn."

—Matitiu 20:1-16

Torinà kínni Jésù nsọ ninu òwe yìi? Lákọ́kọ́, a ni lati mọ̀ pé bí ọkùnrin tí ó jẹ́ baálé kan dúró bí Bàbá, èso tí ó si nfẹ́ kì se èwà sóyà tabi àgbàdo. Ọkàn àwọn ènìyàn ni. Àwọn alágbàse ni wọn yóò máa sojú wa, àwọn tí ó rán jáde lọ fún ìkóre ní pápá. Àwọn nkan méjì ti mo gbàgbọ́ pé Jésù fẹ́ kí á rí. Àkọ́kọ́, se àkíyèsí bí ọkùnrin tí ó jẹ́ baálé kan se ńwa ìrànwọ́.

*Nítorí ìjọba ọ̀run dàbí ọkùnrin tí ó jẹ́ baálé kan, tí ó jíjáde lọ ní kùtùkùtù òwúrọ̀, tí ó gba àwọn alágbàṣe sínú ọgbà àjàrà rẹ̀.*

O tí jíjáde lọ ní kùtùkùtù òwúrọ̀, osì njáde léra ati léra ni gbogbo ọjọ́ nà ó nwá ẹniti ó le rànlọ́wọ́ ninu ọgbà àjàrà rẹ̀. Níkíakia ní ó fẹ́ ẹ. Nitori ìkórè ti pọ́n a sì gbọdọ̀ kórè na ní kía kía, láìjẹ́ bẹ̀ yóò sọnù. Kíyèsi pé ó tún gba àwọn alágbàṣe o kun bí wákàtí kan si àkókò na.

*Ó tún jáde lọ́sàn án ní nǹkan bí wákàtí kẹfà àti wákàtí kẹsànán, ó túnṣe bákan náà. Lọ́jọ́ kan náà ní wákàtí kọkànlá ọjọ́, ó tún jáde sí àárín ìlú, ó sì rí àwọn aláìríṣẹ́ mìíràn tí wọ́n dúró. Ó bi wọ́n pé, "Èéṣe tí ẹ̀yin kì í ṣiṣẹ́ ní gbogbo ọjọ́?"*

*"Wọ́n sì dáhùn pé, 'Nítorí pé kò sí ẹni tí yóò fún wa ní iṣẹ́ ṣe."*

*"Ó tún sọ fún wọn pé, 'Ẹ̀yin náà ẹ jáde lọ ṣiṣẹ́ pẹ̀lú nínú ọgbà àjàrà mi."*

Ohun ìjìnlẹ̀ tí òwe yí sì nìyìí: Kílódé tí o fi kọ́kọ́ san owó fún ẹnití ó gbà gbẹ̀yìn? Ìdáhùn wà nínú ẹsẹ kẹẹ̀dógumn.

*"Nígbà tí àwọn ti a pè ní wákàtí kọkànlá ọjọ́ dé, ẹnìkọ̀ọ̀kan gba owó dínárì kan. Nígbà tí àwọn tí a gbà ṣiṣẹ́ lákọ̀ọ́kọ́ fẹ́ gba owó tiwọn, èrò wọn ni pé àwọn yóò gba jù bẹ́ẹ̀ lọ, ṣùgbọ́n ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn gba owó dínárì kan. Bí wọ́n ti ń gbà á, wọ́n ń kùn sí onílẹ̀ náà, pé, "Wákàtí kan péré ni àwọn tí a gbà kẹ́yìn fi ṣiṣẹ́, ìwọ sì san iye kan náà fún wọn àti àwa náà ti a fi gbogbo ọjọ́ ṣiṣẹ́ nínú oòrùn gangan."*

*"Ṣùgbọ́n ó dá ọ̀kan nínú wọn lóhùn pé, 'Ọ̀rẹ́, kò sí aburú nínú nǹkan tí èmi ṣe sí yín. Kì í ha ṣe pé ẹ̀yin gbà láti ṣiṣẹ́ fún owó dínárì kan. Ó ní, Gba èyí tí í ṣé tìrẹ, ki ó sì máa lọ. Èmi fẹ́ láti fún ẹni ìkẹ́yìn gẹ́gẹ́ bí mo ti fi fún ọ. <u>Àbí ó lòdì sí òfin pé kí èmi fún ẹnikẹ́ni ní owó mi bí mo bá yàn láti ṣe bẹ́ẹ̀? Kí ni ìdí tí ìwọ ní láti bínú nítorí èmi ṣe ohun rere</u>?"*

## <u>KÍ NI ÌDÍ TÍ ÌWỌ NÍ LÁTI BÍNÚ NÍTORÍ ÈMÍ SE OHUN RERE</u>?

Bí a ti rí kà ninu òwe, a le rò wípé, Hey, nkan tí ó se yí kòdára! O le má sọ òótọ́ bí a bá fojú ti ayé yi wòó bí a ti fi wákàtí sisẹ́ dọlladr. Sùgbọ̀n bí mo ti sọ sáájú, kì íse bí Ọlọ́run ti nro nkan nìyẹn. Báále nàa fẹ ri wípé àwọn tí ó wá gbèyìn ni ọjọ́ nà tí òun sì san owó fún nà le ri òun bí onínurere wọn yóò si tún fẹ láti má ba sisẹ. Bẹsì ni báale nàa fẹ kí wọn tọ gbogbo àwọn ọ̀rẹ́ wọn lọ kí wọ́n sì sọ iye tí òun san fún wọn láti leri bí o ti se dáda sí wọn. Torinà kínni ó fi parí òwe na? Ọlọ́run wà nínú oko-òwò àwọn ènìyàn, tí o ba wá dá sí oko-òwò Rẹ, O jẹ́ onínurere yóò sí sán fún ọ gidigidi.

**ỌLỌ́RUN WÀ NÍNÚ OKO–ÒWÒ ÀWỌN ÈNÌYÀN, TÍ Ó BÁSÌ DÁSÍ OKO-ÒWÒ RẸ O JẸ́ ONÍNURERE YÓÒ SÌ SÁN FÚN Ọ NÍ GIDIGIDI.**

## Sé o le gbà lọ̀ọ̀fẹ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run?

Jésù sọ ọ̀kan lára àwọn òwe tí o yanilẹ́nu gan nínú Bíbéli nípa rírí gbà, Mo mọ̀ pé o ti gbọm nípa òwe Ọmọ Onínákúna. Mo fẹ́ kí o lọ kàá, nigbàna a ó wa sọ̀rọ̀ lórí rẹ̀. Dúró dè mí níbíyi a ti fẹ́ dé òpin ìwé nà, mi ò sì fẹ́ kí o lọ títí wà fi gbọ́ mi tán. A rí ìtàn na ninu ìwé Lúkù 15 ó gùn díè, sùgbọ́n fi àyè sílè láti gbé yẹ̀ wò.

*Ó sì wí pé ọkùnrin kan ní ọmọ méjì: "Èyí àbúrò nínú wọn wí fún baba rẹ̀ pé, 'Baba, fún mi ní ìní tí ó kàn mí.' Ó sì pín ohun ìní rẹ̀ fún wọn.*

*"Kò sì tó ọjọ́ mélòó kan lẹ́yìn náà, èyí àbúrò kó ohun gbogbo tí ó ní jọ, ó sì mú ọ̀nà àjò rẹ̀ pọ̀n lọ sí ilẹ̀ òkèrè, níbẹ̀ ni ó sì gbé fi ìwà wọ̀bìà ná ohun ìní rẹ̀ ní ìnákúnàá. Nígbà tí ó sì ba gbogbo rẹ̀ jẹ́ tan, ìyàn ńlá wá mú ní ilẹ̀ náà; ó sì bẹ̀rẹ̀ sí di aláìní. Ó sì fi ara rẹ sọfà fun ọ̀kan lára àwọn ọmọ ìlú náà; òun sì rán an lọ sí oko rẹ̀ láti tọ́jú ẹlẹ́dẹ̀. Ayọ̀ ni ìbá fi jẹ oúnjẹ tí àwọn ẹlẹ́dẹ̀ ń jẹ ní àjẹyó: ṣùgbọ́n ẹnikẹ́ni kò sì fi fún un.*

*"Ṣùgbọ́n nígbà tí ojú rẹ̀ wálẹ̀, ó ní 'Mélòó mélòó àwọn alágbàṣe baba mí ni ó ní oúnjẹ àjẹyó, àti àjẹtì, èmi sì ń kú fún ebi níhìn-ín. Èmi ó dìde, èmi ó sì tọ baba mi lọ, èmi ó sì wí fún un pé: Baba, èmí ti dẹ́ṣẹ̀ sí ọ̀run, àti níwájú rẹ; Èmi kò sì yẹ, ní ẹni tí à bá pè ní ọmọ rẹ mọ́; fi mí ṣe ọ̀kan nínú àwọn alágbàṣe rẹ.' Ó sì dìde, ó sì tọ baba rẹ̀ lọ."*

*"Ṣùgbọ́n nígbà tí ó sì wà ní òkèrè, baba rẹ̀ rí i, àánú ṣe é, ó sì súré, ó rọ̀ mọ́ ọn ní ọrùn, ó sì fi ẹnu kò ó ní ẹnu.*

*"Ọmọ náà sì wí fún un pé, Baba, èmi ti dẹ́ṣẹ̀ sí ọ̀run, àti níwájú rẹ, èmi kò yẹ ní ẹni tí à bá pè ní ọmọ rẹ mọ́!*

*"Ṣùgbọ́n baba náà wí fún àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀ pé, Ẹ mú ààyò aṣọ wá kánkán, kí ẹ sì fi wọ̀ ọ́; ẹ sì fi òrùka bọ̀ ọ́ lọ́wọ́, àti bàtà sí ẹsẹ̀ rẹ̀: Ẹ sì mú ẹgbọrọ màlúù àbọ́pa wá, kí ẹ sì pa á; kí a máa ṣe àríyá: Nítorí ọmọ mi yìí ti kú, ó sì tún yè; ó ti nù, a sì rí i. Wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe àríyá.*

*"Ṣùgbọ́n ọmọ rẹ̀ èyí ẹ̀gbọ́n ti wà ní oko: bí ó sì ti ń bọ̀, tí ó*

*súnmọ́ etí ilé, ó gbọ́ orin àti ijó. Ó sì pe ọ̀kan nínú àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ wọn, ó béèrè, kín ni a mọ nǹkan wọ̀nyí sí? Ó sì wí fún un pé, 'Arákùnrin rẹ dé, baba rẹ sì pa ẹgbọrọ màlúù àbọ́pa, nítorí tí ó rí i padà ní àlàáfíà àti ní ìlera.' Ó sì bínú, ó sì kọ̀ láti wọlé; baba rẹ̀ sì jáde, ó sì wá í ṣìpẹ̀ fún un. Ó sì dáhùn ó wí fún baba rẹ̀ pé, 'Wò ó, láti ọdún mélòó wọ̀nyí ni èmi ti ń sìn ọ́, èmi kò sì rú òfin rẹ rí: ìwọ kò sì tí ì fi ọmọ ewúrẹ́ kan fún mi, láti fi bá àwọn ọ̀rẹ́ mi ṣe àríyá: Ṣùgbọ́n nígbà tí ọmọ rẹ yìí dé, ẹni í ó fi panṣágà fi ọrọ̀ rẹ ṣòfò, ìwọ sì ti pa ẹgbọrọ màlúù àbọ́pa fún un."*

*"Ó sì wí fún un pé, 'Ọmọ, nígbà gbogbo ni ìwọ ń bẹ lọ́dọ̀ mi, ohun gbogbo tí mo sì ní, tìrẹ ni. Ó yẹ kí a ṣe àríyá kí a sì yọ̀: nítorí arákùnrin rẹ yìí ti kú, ó sì tún yè; ó ti nù, a sì rí I.'"*

—Lúkù 15:11-32

Lákọkó, a nílò lati mọ ìdí tí ó mu kí ọmọkùnrin na fi fi ilé baba rẹ̀ sílẹ̀. Ìdáhùn na nipé bí o ti se nrí bàbá bí ẹ̀gbọ́n rẹ̀ na ti npe bàbá wọn ni olùsàkóso tíkò dára. Rántí pé ẹ̀gbọ́n rẹ̀ na sọ pé Wò ó, láti ọdún mélòó wọ̀nyí ni èmi ti ń sìn ọ́, èmi kò sì rú òfin rẹ rí: ìwọ kò sì tí ì fi ọmọ ewúrẹ́ kan fún mi, láti fi bá àwọn ọ̀rẹ́ mi ṣe àríyá. Sí ẹ̀gbọ́n rẹ̀ bàbá wọn burú olùsàkóso sì ni. Ó le wòó wípé kílódé tí ẹ̀gbọ́n nà kò se lọ pèlú àbùrò re. Èrò nìkan ni èyí, sùgbọ́n nínu àsà àwọn Juu, ẹ̀gbọ́n ni yóò jogún ìlọpo méjì ogún nigbatí bàba woṇ bá kú. Abúrò kò ní ẹ̀tọ́ sí ánfání yi. Mo ròpé ohun tí ẹ̀gbọn rò nipé ọjọ́kan yóò jẹ́ ọjọ́kan tí gbogbo nkan yó di tirẹ̀, ó wa wo pé ó yẹ kí òun kú dúró.

Èyí àbúrò fẹ́ wá ibi pápá oko tútu̇̀ lọ síbòmíràn ati jáde kúrò lábẹ́ òfin bába rẹ̀, ó wá mú ìpin tirẹ̀ ninu ógún ó sì bá tirẹ̀ lọ. Sùgbọ́n nígbàti ó lọ tán, ó wá bá ara rẹ̀ ninu ayé tí kò lérò. Lẹ́kanna ni gbogbo owó rẹ̀ tán, ó wá ri pé orílẹ̀-èdè tí ohun sálọ gbogbo wọn ni kò ní owó mọ́. Ìyàn ńlá ti wà ní ilú nà. Ó wá nwá óunjẹ kiri, ó se ohunkan tí ó sàjèjì sí òun ná pẹ̀lú. Ó wá ta ara rẹ̀ nitori oúnjẹ. Ìgbà àkọ́kọ́ si nìyí tí yóò fi ara sọfà fún ounjẹ láti ìgbà tí wọn ti bi sáyé. Sáájú, wọ́n ńtọ́jú rẹ̀ nitori ẹnití ó jẹ, kì isé nitori ohun tọ se. Níbayí ó ní lati sisẹ́, isẹ́ kan tí o sì ri nà ni lati máa fun àwọn ẹlẹ́dẹ̀ ní ounjẹ, Isẹ́ ìdọ̀tí ti o sì jẹ́ ti ẹlẹ́sẹ̀ fún àwọn Juu. Bíbélì sọ pé ebi sì ń pá gidigidi tí o fi ńjẹ oúnjẹ tí àwọn ẹlẹ́dẹ̀ ń jẹ ní àjẹyó: ṣùgbọ́n ẹnikẹ́ni kò

sì fi fún un. Ìdi nípé? Gbogbo ènìyàn ni ó wa nínu ọkọ̀ kan na pẹ̀lú rẹ̀, Kòsí owó, bí wọ́n o ti làájá ni ó kù. Sé o ti gbọ́ irú ohun yí ri? Ó dára, ní ọjókan nígbà tí ojú rẹ̀ wálẹ̀, ó sì rántí ó ní 'Mélòó mélòó àwọn alágbàṣe baba mí ni ó ní oúnjẹ àjẹyó, àti àjẹtì.

*"Ṣùgbọ́n nígbà tí ojú rẹ̀ wálẹ̀, ó ní "Mélòó mélòó àwọn alágbàṣe baba mí ni ó ní oúnjẹ àjẹyó, àti àjẹtì, èmi sì ń kú fún ebi níhìn-ín. Èmi ó dìde, èmi ó sì tọ baba mi lọ, èmi ó sì wí fún un pé: Baba, èmí ti dẹ́ṣẹ̀ sí ọ̀run, àti níwájú rẹ; Èmi kò sì yẹ, ní ẹni tí à bá pè ní ọmọ rẹ mọ́; fi mí ṣe ọ̀kan nínú àwọn alágbàṣe rẹ." Ó sì dìde, ó sì tọ baba rẹ̀ lọ.*

Nígbàti ó wá ye pé ọ̀pọ̀ ounjẹ ni ó wà nilé, ó dìde ó sì gba ilé bàba rẹ̀ lọ kì íse bí ọmọ mọ́ bíkòse bí alágbàse. Èmi ó dìde, èmi ó sì tọ baba mi lọ, èmi ó sì wí fún un pé: Baba, èmí ti dẹ́ṣẹ̀ sí ọ̀run, àti níwájú rẹ; Èmi kò sì yẹ, ní ẹni tí à bá pè ní ọmọ rẹ mọ́; fi mí ṣe ọ̀kan nínú àwọn alágbàṣe rẹ.' "Ṣùgbọ́n nígbà tí ó sì wà ní òkèrè, baba rẹ̀ rí i, baba re ó sì súré, ó rọ̀ mọ́ ọn ní ọrùn, ó sì fi ẹnu kò ó ní ẹnu.

*"Ṣùgbọ́n nígbà tí ó sì wà ní òkèrè, baba rẹ̀ rí i, àánú ṣe é, ó sì súré, ó rọ̀ mọ́ ọn ní ọrùn, ó sì fi ẹnu kò ó ní ẹnu."*

Ẹ jẹ́ kí á ni òye àwòrán ohun tí ó nṣẹlẹ̀ níbiyi dáda, nitori ìtàn yí ń fi àpẹẹrẹ ẹni tí Bàbá wa Ọlọ́run jẹ́ sí wa hàn. Ọmọ ti padà wá láti ọ̀dọ̀ àwọn ẹlẹ́dẹ̀. Nínu òfin àwọn Juu, ó ti di aláìmọ́. Ní kéte tí bàba rẹ̀ ti ó rọ̀ mọ́ ọn ní ọrùn òun na ti di aláìmọ́, sùgbọ́n ó mọ̀ ọ́n mọ̀ sé fún ìfẹ́ tí o ní sí ọmọ rẹ̀. Dípò kí o bá ọmọ na wí ati nà fún àsìse tí ó se ati ìwà òmùgọ̀ rẹ̀, bàba rẹ̀ Ẹ mú ààyò aṣọ wá kánkán, kí ẹ sì fi wọ̀ ọ́. Ó tún ní kí wọn sì fi òrùka bọ̀ ọ́ lọ́wọ́, tí ó túmọ̀ sí àsẹ bị ọmọ tí a ti ràpadà. Lẹ́yìn rẹ̀, o fi bàtà sí ẹsẹ̀ rẹ̀, tí o túmọ sí ẹ̀tọ́ ati wọlé sí gbogbo ìní rẹ̀. Wà rí àsà yí ninu ìwé Rútù 4:7.

(*Ní ayé ìgbàanì, kí a tó le sọ wí pé ohun ìràpadà tàbí pàṣípàrọ̀ ohun ìní fi ìdí múlẹ̀ ní ilẹ̀ Israẹli, ẹnìkan ni láti yọ bàtà rẹ̀ kúrò ní ẹsẹ̀ rẹ̀ kí ó sì fi fún ẹnìkejì, ó jẹ́ òfin fún ẹni tí ó fẹ́ rà á. Nípa ṣíṣe èyí, àwọn ará Israẹli fihàn wí pé ọ̀rọ̀ náà ti fidímúlẹ̀.)*

Ohun tó parí rẹ, bàbá rẹ̀ sì pa ẹgbọrọ màlúù àbọ́pa.

Ọmọ yí padà wálé lérò wípé wọn o fi òun se alágbàse, sùgbọn Bàbá rẹ̀ gbà padà bí ọmọ rẹ̀.

*Emi ó sì wí fún un pé: Baba, èmí ti dẹ́ṣẹ̀ sí ọ̀run, àti níwájú rẹ; Èmi kò sì yẹ, ní ẹni tí à bá pè ní ọmọ rẹ mọ́; fi mí ṣe ọ̀kan nínú àwọn alágbàṣe rẹ.*

*Ẹ mú ààyò aṣọ wá kánkán, kí ẹ sì fi wọ̀ ọ́; ẹ sì fi òrùka bọ̀ ọ́ lọ́wọ́, àti bàtà sí ẹsẹ̀ rẹ̀: Ẹ sì mú ẹgbọrọ màlúù àbọ́pa wá, kí ẹ sì pa á; kí a máa ṣe àríyá: Nítorí ọmọ mi yìí ti kú, ó sì tún yè; ó ti nù, a sì rí i. Wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe àríyá.*

Sùgbọ́n ipa tí ó kàn nísiyi ninu ìtàn yí ni mo fẹ́ kí o rí.

*"Ṣùgbọ́n ọmọ rẹ̀ èyí ẹ̀gbọ́n ti wà ní oko: bí ó sì ti ń bọ̀, tí ó súnmọ́ etí ilé, ó gbọ́ orin àti ijó. Ó sì pe ọ̀kan nínú àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ wọn, ó béèrè, kín ni a mọ nǹkan wọ̀nyí sí? Ó sì wí fún un pé, 'Arákùnrin rẹ dé, baba rẹ sì pa ẹgbọrọ màlúù àbọ́pa, nítorí tí ó rí i padà ní àlàáfìà àti ní ìlera.' Ó sì bínú, ó sì kọ̀ láti wọlé; baba rẹ̀ sì jáde, ó sì wá í ṣìpẹ̀ fún un."*

*Ó sì dáhùn ó wí fún baba rẹ̀ pé, "Wò ó! Láti ọdún mélòó wọ̀nyí ni èmi ti ń sìn ọ́, èmi kò sì rú òfin rẹ rí: ìwọ kò sì tí ì fi ọmọ ewúrẹ́ kan fún mi, láti fi bá àwọn ọ̀rẹ́ mi ṣe àríyá: Ṣùgbọ́n nígbà tí ọmọ rẹ yìí dé, ẹni í ó fi panṣágà fi ọrọ̀ rẹ̀ ṣòfò, ìwọ sì ti pa ẹgbọrọ màlúù àbọ́pa fún un!"*

*"Ó sì wí fún un pé, 'Ọmọ, nígbà gbogbo ni ìwọ ń bẹ lọ́dọ̀ mi, ohun gbogbo tí mo sì ní, tìrẹ ni. Ó yẹ kí a ṣe àríyá kí a sì yọ̀: nítorí arákùnrin rẹ yìí ti kú, ó sì tún yè; ó ti nù, a sì rí i."*

Nigbati eyi egbon de egbe ile, o ko lati wo inu ile nigbati o ri ohun ti onsele. Gbo nkan ti o so *Wò ó, láti ọdún mélòó wọ̀nyí ni èmi ti* ***ń sìn*** *ọ́, èmi kò sì rú òfin rẹ rí: ìwọ kò sì tí ì fi ọmọ ewúrẹ́ kan fún mi, láti fi bá àwọn ọ̀rẹ́ mi ṣe àríyá."* O nso pe baba awon le o buru, atipe kin ni o pe ara re? Eru! Sùgbọ́n kín ni bàbá rẹ̀ pèé ninu ẹsẹ 31 Ọmọ mi! Ohun tí mo ń sọ nìyí.

Èrò ọkàn yí ní ìwọ na bá dàgbà sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́run bí àwọn ọmọ méjì yí ni si baba won, pé ẹni tí ó le tí ó burú sì ni olùsàkóso, pé kò sì èrè kankan nínu sínsìn. Ẹ̀sin tí kò pé oní láti sisé fún Ọlọ́run ki ́o tó le tẹwọgbà ọ. Àwòrán ti ọmọ kékeré ní nípa bàbà rẹ yípadà, síbẹ̀síbẹ̀, nígbàtí bàba rẹ gbàá padà lai bawí tí ó sì tún gba padà bí ọmọ láise ẹrú. Ìbásepọ̀ èyí àgbà pẹ̀lú baba rẹ̀ dálé ohun tí o se o ri bi pé o ńse ẹrụ́ fun àti gbìyànjú ati se ohun tí ó tó. Nigbàti o bá dá ara rẹ mọ̀ nipa ohun tí o bá ń se, wa ma se àsìse wa si ma se ìdájọ àwọn tí ó wa ní àyíká rẹ bí ẹnití inu wọn kò dùn sí o. Súgbọ́n òtítọ ibẹ̀ nipé, èyi ẹ̀gbọ́n rí bí ẹníti ó le tí o sì burù dé ibi pé kò le gba ohunrere láti ọ̀dọ̀ bàbá rè. Nígbàti ó nsọ pé nkan tí babá rẹ̀ se kò dára, tí ó sì ní ko ti fún ohun ní tí ì fi ọmọ ewúrẹ́ kan fún mi, láti fi bá àwọn ọ̀rẹ́ mi ṣe àríyá. Nkan tí bàbá rẹ sọ nìwọ̀nyìí.

*Ó sì wí fún un pé, "Ọmọ mi," "nígbà gbogbo ni ìwọ ń bẹ lọ́dọ̀ mi, ohun gbogbo tí mo sì ní, tìrẹ ni."*

Kò sọ pé "Ẹrú mi" Ọmọ ni ó pe! Ọmọ ni ó ni ohun gbogbo tí baba rẹ̀ bá ní: ẹbí kanna ni wọn. Ẹrú kò ni ogún ìní kankan. Sé o ti ri, Èyí ẹ̀gbọ̀n ní ẹ̀tọ́ sí ohnugbogbo tí wọn ní. Sùgbọ́n ojú tí o fi ńwo ara rẹ kò fún ni àyè láti le jẹ ìgbádùn nkan tí nse tìrẹ nítorí tí ò nrí ara rẹ bí alágbàse.

Kínni ìdí tí mo fi fi àyè sílẹ̀ láti se gbogbo àlàye yi fún ọ? Nítorí o má nle fún alágbàse láti le gba nkan ní owọ Ọlọrun" Wọn ma nrò wípe àwọn gbọdọ̀ wá ojúrere rẹ nà; àti pé ti àwọn bá ti le se àsìse, ojú yóò ma tìwọ́n. Wọn o ma bẹ̀rù, àti rí ara wọn bí ẹnití kò yẹ láti gbà ní owọ baba. Àyàfi tí o bá tún èrò rẹ yí se, o kò ní le rí gbà lọ̀ọ̀fẹ́ lọwọ̀ Baba. Kí o sì ránti, a nílò lati le gbàá lọ̀ọ̀fẹ tí a bá fẹ́ jẹ́ ẹniti onínurere bí Baba.

O le dúró nítítọ̀ níwájú Ọlọ́run; ẹ̀bùn ìfẹ́ rẹ̀ ṡ̀ ọ ni. Mo fẹ́ràn ohun tí Máttíù 3:16-17 sọ.

*Bí ó si tí ṣe ìtẹ̀bọmi fún Jesu tán, Ó jáde láti inú omi. Ní àkókò náà ọ̀run ṣí sílẹ̀ fún un, Ó sì rí Ẹ̀mí Ọlọ́run ń sọ̀kalẹ̀ bí àdàbà, ó sì bà lé e. Ohùn kan láti ọ̀run wá sì wí pé, "Èyí sì ni àyànfẹ́ ọmọ mi, ẹni tí inú mi dùn sí gidigidi."*

Àsìkò yí gan ní Jésù bẹ̀rẹ̀ isẹ́ ìránsẹ́ rẹ̀. Kò ti se ohnu kan kan síbẹ̀ láti le jẹ́ kí Ọlọ́run gbóríyìn fun, sùgbọ́n kíyèsi ohun tí Ọlọ́run sọ. Pé Òn fẹ́ràn rẹ̀ Inú rẹ̀ sì dùn sí.

Sé o sì rántí àwọn olè méjì tí wọ́n wà lóri àgbélébu nígbatí Jésù na wà lórí igi àgbélébu? Ọ̀kan ninu wọn sọ pé "Rántí mi nigbati o bá dé ìjọba rẹ." Jésù dálóhùn pé, "Lóòtọ́ ni mo sọ fún ọ, lónìí ni ìwọ yóò pàde mi ni Páradísè." Kín ni ohun tí ó se tí ó fi yẹ fún? KÒSÍ!

Nígbàti a bá pe orúkọ Jésù, Bíbélì sọ pé a di àtúnbí a tàtapò wa láti inú ìjọba òkùnkùn sínu ìmọlẹ̀ ti Ìjọba Ọlọ́run Kín ni nkan tí a se kí á tó gbàá? KÒSÍ.

Torinà bí mo ti ń mú ìpín yi wá sí ìparí jọ̀wọ́ rántí pé gbogbo nkan wọ̀nyí ti Ọlọ́run fi ránsẹ́ sí mi ninu ọdún yi kò tọ́ símí. Ó kàn nránmí lọ́wọ́ nì lati le ní òye pé mo gba Ìjọba Rẹ̀ nigbatí mo bá pe orúkọ Jésù. Kì íse dandan ni kí ngbà wọ́n. Mo kàn nílò láti gba Ojúrere àti inúrere Rẹ̀. Níwọ̀n ti o ba ti le gba inúrere RẸ̀, ìwọ na le jẹ́ oninurere ati pẹ̀lú ojúrere Rẹ̀.

ORÍ KỌKÀNLÁ

# ÌLÉRÍ FÚN ÀWỌN TÍ WỌ́N JẸ́ ONÍNÚRERE

Bill àti ìyàwó rẹ̀ April, ní iṣẹ́ kékeré kan tí ó ńse nínú ẹbí wọn láti bí ọdún mẹ́rìnlà iṣẹ́ títún ẹ̀rọ omi se. Gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn ọmọ ìjọ wa Faith Life Church. Wọ́n ti rí bí ìjọ tí ńdàgbàsókè àti gbọ́ gbogbo àwọn oríṣi ìtàn ti ìṣẹ́gun ti á ní. Toríbẹ́ nígbàtí ó ńgbọ́ nípa pé a fẹ́ mú ìmúgbòrò bá ìjọ Faith Life Church kí a ba le ní ipá tótóbi ní agbègbè wa, àwọn na ti setán láti kópa.

April pín pẹ̀lú wa pé òun ti pinnu láti fi ẹ̀ẹ́gbàárùn pọ́ùn sílẹ̀ fún iṣẹ́ nà, ṣùgbọ́n ohun ìyàlẹ́nu ni ó jẹ́ fún un nígbàtí  Bill padàdé láti ilé ìtajà tí ó lọ ra  ohun jíje dé, tí ó ní Olúwa sọ fún òun pé kí àwọn fi ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta lé *ní* ọ̀kẹ́ mẹ́ta àbọ̀ pọ́udn sílẹ̀ kì íse ẹ̀ẹ́gbaàrún pọ́ùn.

Wọn kòsì tí mọ ibití wọn ó ti rí owó nà April na gbà pé kí àwọn fi ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta lé *ní* ọ̀kẹ́ mẹ́ta àbọ̀ pọ́ùn sílẹ̀ fún iṣẹ́ ìmúgbòrò nà. Ṣùgbọ́n, wọ́n kò ní owó nà lọ́wọ́, wọn kò sì mo ọ̀nà tí owó na yóò gbà wa.

Níbi ọ̀sẹ̀ melo sí ìgbàna, àwọn ilé iṣẹ́ olómí ní ìlú na ránṣẹ́ sí wọn pé àwọn fẹ́ láti se gbogbo àtúnse àwọn ẹ̀rọ omi ìlú wọn wa pe wọ́n pé wọn le se wọ́n sí dáhùn pé bẹ́ẹ̀ni iṣẹ́ sì wá bẹ̀rẹ̀ nípa fífi ọwọ́ sí ìwé òfin tí ó de isẹ́ nà láti se. April ní ìwé tí wọn kọ lórí iṣẹ́ nà lé ní ọgọ́run ojú ìwé, tí wọn sì ní láti se ohun gbogbo tí ó yẹ. Ìlànà lórí àti gba iṣẹ́ nà gbomimu, ṣùgbọ́n wọ́n ti se gbogbo rè Wọ́n wá ri wípé àwọn nìkan ni ilé iṣẹ́ tí ó   fẹ́ se iṣẹ́ nà, wọ́n kò sì mọ bí wọn ti se gbé iṣẹ́ nà wá bá wọn.

Ní kété tí wọn ti gbé ìwé àdéhùn iṣẹ́ nà lé wọn lọ́wọ́ padà, ìlú pè wọ́n pé àwọn wo pé ilé iṣẹ́ wọn kéré láti le se iṣẹ́ ìlú nà nítori ó ma tó ìgba ojúlé tí wọn gbọ́dọ̀ parí lárin ọjọ́ márùndín lọ́gọ́rin. Ṣùgbọ́n lẹ́yìn

ìjíròrò, wọ́n rí àrídájú pé wọ́n le ṣé.

Bill ní iṣẹ́ nà wá di ohun tí òun àti òṣìṣẹ́ òun ńṣe ní tọ̀sán tòru àti bákanna ní ọjọ́ Àbámẹ́ta tí ńse ọjọ́ Sátidé. Ṣùgbọ́n ṣé o wá rí? Wọ́n parí gbogbo iṣẹ́ nà ní àsìkò wọ́n sì wá le rí ẹ̀ẹ́dẹ́gbàta lé *ní* ọ̀kẹ́ mẹ́ta àbọ̀ pọ́ùn gbé sílẹ̀ fún isé inú ìjọ àti san gbogbo gbèsè tí wọ́n ti jẹ sílẹ̀ na pẹ̀lú. Inú wọn sì dùn!

Wòó Ọlọ́run ní ètò ńlá fún Bill àti April jú èyíti wọn ní fún ara wọn lọ. Ó mọ ọkàn wọn sí Òn, ṣùgbọ́n Ó fẹ́ kí agbára wọn tún nà si.

Níbáyìí, wọ́n ti pè wọ́n fún iṣẹ́ tí ìjọba nígbati wọn rí pé wọ́n ti parí iṣẹ́ ìlú tí wọn gbé lé wọn lọ́wọ́, ìlẹ̀kùn àwọn iṣẹ́ nlá ti sí fún ọjọ́ iwájú fún wọn.

Ọlọ́run fẹ́ràn láti má na ọwọ́ àwọn èniyàn síwájú. Ó mọ ìrísí wa ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀ ìgbà, ni a kò mọ èyí ti a sì nílò láti fi hàn wá ni, ìlànà tí ó yẹ kí á mọ̀ nìyí.

> *A sì tún fi ìjọba ọ̀run wé ọkùnrin kan tí ó ń lọ sí ìrìnàjò. Ó pe àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀, ó sì kó ohun ìní rẹ̀ fún wọn. Ó fún ọ̀kan ni tálẹ́ǹtì márùn-ún, ó fún èkejì ni tálẹ́ǹtì méjì, ó sì fún ẹ̀kẹta ni tálẹ́ǹtì kan, ó fún olúkúlùkù gẹ́gẹ́ bí agbára rẹ̀ ti mọ, ó sì lọ ìrìnàjò tirẹ̀. Ọkùnrin tí ó gba tálẹ́ǹtì márùn-ún bẹ̀rẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ láti fi owó náà ṣòwò. Láìpẹ́, ó sì jèrè márùn-ún mìíràn. Ọkùnrin tí ó gba tálẹ́ǹtì méjì náà fi tirẹ̀ ṣòwò. Láìpẹ́, ó sì jèrè tálẹ́ǹtì méjì mìíràn. Ṣùgbọ́n ọkùnrin tí ò gba tálẹ́ǹtì kan, ó wa ihò ní ilẹ̀, ó sì bo owó ọ̀gá mọ́ ibẹ̀.*
>
> —Máttíù 25:14-18

Àti ka òwe yí ṣáájú, ṣùgbọ́n mo fẹ́ fi nkankan tí a kò tí gbéyẹ̀wò hàn wá.

Kíyèsí pé nígbati ẹniti ó ní ilẹ̀ ńfi iṣẹ́ lé àwọn ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ̀ lọ́wọ́, ó ní mo tí fi iṣẹ́ ná léyìn lọ́wọ́ "gẹ́gẹ́ bí agbára olúkúlùkù yín." Èyí tí a fún ni àpò wúrà tálẹ́ntì márun túmọ̀ sípé o ní agbára láti lo àpò márun tálẹ́ntì wúrà ná . Tí ó bá tún sì ní agbára jùbẹ lọ ni, olúwa rẹ̀ kò bá sì fun ní ọ̀pọ̀ jùbẹlo. Bẹ́ẹ̀ na sì ni fún ọmọ-ọ̀dọ̀ tí a fún ní méjì.

Ṣùgbọ́n wo nkan tí ó ṣelè. Ọmọ-ọ̀dọ̀ tí ó gba àpò máarún wúrà sọ

di mẹ́wa ó mú kí ó pọ̀si. Ní ọ̀na yí kanna, Kínni ohun tí ó ṣẹlẹ̀? Ó da, ní ọ̀nà tí o gbà rọrùn, agbára rẹ̀ pọ̀si ó pọsi láti ìpele márun lọ sí mẹ́wa. Agbára rẹ̀ láti se ojúse tàbi iṣẹ́ tún ti pọ̀si. Ó wá di ẹniti ọ níye lórí tí ó wúlò níwájú olúwa rẹ̀ ó sì ti pèsè ara rẹ̀ ṣílẹ̀ fún ìgbéga.

Níbáyi, ọgbọ́n olúwa rẹ sìnìyí. Ó mọ ìwà ọmọ-ọ̀dọ̀ tí ó fún ní àpò márún wúrà Ọ́ mọ̀ pé ọ̀ ní. ìrísí láti le dìde dé ipò titun tó wà, Bíotilẹ̀jẹ́pé, àpò wúrà máàrún ni olúwa rẹ̀ fún, tí ise ìwọ̀n agbára tí ó ni nígbàna, iṣẹ́ tí ó fi le lọ́wọ́ ni bi yóò ti se ni ọ̀pọ̀ ìkórè sí ju bí ọmọ-ọ̀dọ̀ na ti bẹ̀rẹ̀ lo èyí tí yoò gbe lọ sí ìpele titun tí agbára rẹ̀ tún le ká.

Olúwa rẹ mọ̀ pé ọ̀nà tí ó le mú kí ọmọ-ọ̀dọ̀ na níye lórí ni kí o na ọwọ́ rẹ̀ jáde kí o sìle sàwárí agbára tí ó ní fúnrarẹ̀. Ọ̀nà yí kan na ni Ọlọ́run ńlò nínú ayé wa kí á le wúlò àti níye lórí àti le kọ wa fún àyànmọ wa.

*Ẹni tí ó bá ṣe olóòótọ́ ninu nǹkan kékeré yóo ṣe olóòótọ́ ninu nǹkan ńlá.*

—Luku16:10

Gẹ́gẹ́ bí mo ti sọ nínu ìpín tí ó sáájú, kòsí iṣẹ́ àkànse kékeré. Wàá sì ma dàgbàsókè nípasẹ̀ ọ̀kọ̀kan, ọ̀kọ̀kan yí yóò sì ma fi kún agbára rẹ sí ìpele tókàn.

Mo ti wà nínu ìlànà yí fún ọjọ́ pípẹ́. Ní ìgbákúgbà, tí mo bá fẹ́ ronu pé, *Rárá, mi ò le se eléyi: Mi ò ti lemọ̀ bí ma ti se, tàbí mi ò tilẹ̀ ri àyè.* Ṣùgbọ́n nígbakúgba tí mo bá ti sọ pé, “Bẹ̀ẹ̀ni, má nà jáde” ma sì ní agbára àti dé ibití mo fẹ́.

Àwọn ènìyàn le wo ayé mí kí wọ́n sì rò pé, *Oh a jẹ pé ó rọrùn láti bọ kúrò ní oko gbèsè, láti le wà lórí tẹlifísiọ̀nu, láti le ní ọkọ̀ ojú òfurufú. Ẹ wo irú ayé tó dára ni.* Ó dára, mà gbà pẹ̀lú rẹ—ayé tó dára; ayé tó dára àti ayé ológo ni! Ṣùgbọ́n o kò mọ bí ayé mí ti se de ibití ó wà loni yi. O mọ irú ìfaradà tí mo ti ní, ní ọ̀pọ̀ ìgbà lábẹ́ wàhálà, kín tó dìde dé ipò agbára yí.

Mo sì tún ńdàgbà, Ọlọ́run sì tún fún mi ní iṣẹ́ àkànse tí ó tún tóbi. Mo mọ̀ pe gbogbo ìgbà ni mó náwó pẹ̀lú àwọn isé àkànse tótóbi àti mo si nà pẹlú nílò owó tó pọ̀ láti le se àsepari gbogbo wọn. Ṣùgbọ́n èmi kò

ní ta ìtura na (àti pé nígbàmíràn ó má ri juju) fún ayé, nítori ètò ìkọ́ni Ọlọ́run ní ó rànmílọ́wọ́ láti se àse parí gbogbo ohun tí a pè mí sí láti pari.

Tí mo bá le gbà ọ ní ìmọ̀ràn kan, Yóò jẹ́ MÁSE LỌ KÚRÒ! Gba Ọlọ́run ní ayè láti nà ọ́ bí ẹnití ó yẹ kí o jẹ.

Ọlọ́run ma´ jáde wá. Kí sì kùnà. Ọjọ́ ọla rẹ wà níwájú rẹ, ó sì ní láti tẹ̀síwájú.

**Sé o mà gba Ọlọ́run láàyè láti nà ọ́?**

Mo wà nínú ìpàdè àdúrà alẹ́ Ọjọrú. Ọmọ mi ni ó sì ńdarí àdúrà nígbàtí ó sàdédé dákẹ́ lójijì, ó sì wo mí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí ní sọ asọ̀tẹ́lẹ̀. Àwọn ohun tí o sọ níwọ̀nyìí:

> Olúwa sọ pé, ìkórè ná pọ̀ jù fún ọ́. Mo sì na ọwọ́ rẹ. Nípa Ẹ̀mi mí nìkan ní o le fi ní oyè ohun tí ó fẹ́ sẹlẹ̀. Sé wà jáde wá, jẹ́ kí Ndarí rẹ sí ibi àwọn ohun tí o le kọjá oye rẹ, àwọn kosese?”

Mo ro pé*, Oh rárá, mo mọ ohun ti on sọ.* Kì íse ìgbà àkọ́kọ nìyíí tí ma jáde.

Mo mọ̀ rírí pé Ọlọ́run tilẹ̀ nbi mí lérè pé sé mà gba Òn láyè láti darí mi nínu àwọn ohun tí o le, tí kò séese, Mo mọ̀ pé wọ́n wà fún ìtàn ńla ní nígbàtí o bá ti rìn nínu wọn tí Ọlọ́run sì ńfi ara rẹ hàn.

Sùgbọ́n bẹ́ẹ̀ na ni mo mọ ìrora tí ó wà nínu kí ènìyàn na wo, ìdíyelé tí wà san fún lílọ sí ibití o kò ti dé rí. Sùgbọ́n, sùgbọ́n SÙGBỌ́N ńlá ni eléyi, Mo sì tún mọ ojúrere Ọlorun ètò ti ìgbéga Rẹ̀, Toribẹ̀ ni mo se sọ pé “BẸ́Ẹ̀NI!” lẹ́sẹ̀kesè.

Ọlọ́run fé mú agbára tí ó fi sínu rẹ jáde. Ọ̀nà kansoso sì niyi tí o le mú ọ dé ibi àyànmọ rẹ. O ní láti nà ọ́! Báwo sì ni Ọlọ́run si ti má nà wá? *Títẹ̀.*

Tí o ba fọn kudukúdu tí o sì gbà kí atẹ́gùn inú rẹ̀ jáde lọ, kudukúdu na yó ti nà si; ó tóbí sí. Bákanna ní fún èmi àti ìwọ. Níkété tí a bá ti gbà kí ó tẹ wá tí a kò sì sá kúrò, agbára ndágbà sí ni. Agbára túmọ̀ si isẹ́

àkànse tó tóbí àti ayẹ̀wò tó tóbi. Sé o mò, Òrò àwàdà ni nígbati o bá nsọ́rọ̀ nipa jíjẹ́ ẹniti ó lawọ́ títí di ìgbà tí Ọlọ́run bá sọ fún ọ pé kí o fi ọ̀kẹ́ màrún pọ̀ùn sílẹ̀. Tàbí kí o fi ọkọ̀ rẹ tí o fẹ́ràn jù lọ sílẹ̀. Ìgbẹ́kẹ̀lé rẹ ṇinu Ọlọ́run ní láti dàgbà si, àti agbára rẹ naà ṇi láti dàgbàsókè.

Ní bi ọ̀sẹ̀ melo lẹ́yìn tí mo sọ pé bẹ̀ẹ̀ni fún Ọlọrun nínu ìpàdé nà, Mo wá rí nkan na tí ó jẹ. Isẹ́ orí telifisiọ́nù ti á ǹse, èyí ti ó má wáyé lẹkan lọ́sẹ̀, ọjọ́kan láàrin ọ̀sẹ̀, ní wọn fẹ́ kí a má wá sé ní *ojojúmọ́*. Ó dàbí nkan tó dára, sùgbọ́n àwọn ǹkan díẹ̀ wà tí ó le mú kí ìyípadà na rọrùn. Àkọ́kọ́ owó ti a ńsan lórí afẹ́fẹ́ yóò tún lọ sókè si ní ìdá ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ́ta lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, àti pé kí á tó san owó tí à ńsan lọ́sẹ̀ gan ní ìgbàna. dàbí ǹkan. Èkejì, a ní láti má pèsè ètò máàrún ní ọ̀sẹ̀ kan a kòsì ti ní ẹ̀ka ilé isẹ́ tẹlifisiọ́nù. Ní àsìkò yí àti gbé ètò wá kan lọ́sẹ̀ lori tẹlifisiọ́nù fún ilé isẹm kan tí yóò wá se àkálẹ̀ ètò mẹrin ní ọ̀sẹ̀ kan fún osù tí à ńlò lọ. wọ́n ó nílò láti tún ètò ná gbékalẹ̀, tí wọn yóò wá gbé àwọn ètò na sórí nẹ́tíwọ́kì, kí wọ́n sì se gbogbo isẹ́ nà. Ní gbànà ni mo ti mọ̀ pé mo ni láti gbem ohun gbogbo tí ó wà nínu ilé jáde kí ba lé sée. Ìsòro ńlá tí a ní nipé èmi ati Drenda kò mọ̀ bí ati se le kọ èka ilẹ́ isẹ́ TV. Sùgbọ́n à gbìyànjú láti se nkankan.

Nípa ti owó nínà, a sese parí ọgbà ile ẹ̀kọ́ ti ìjọ wa, kò sì tí sí owó kan tí ó sẹ́ kù nílẹ̀ láti le fi kọ́ ilé isẹ́ Tẹlifisiónù. Lati le má sisé. a ní láti ra àwọn ohun èlò bí kámẹ́rà àti gba àwọn òsìsẹ́ láti máa sisẹ́. Àwọn ọjọ́ kan wà tí ó dàbí pé kò le séese. Sùgbọ́n Ọlọ́run jẹ́ Olọ́tító ó sì ńgba èmi àti Drenda níyànjú a sì tí lọ tí a fi sẹ́.

Ìdíwọ́ ńlá kan wá yọjú ní bí osù mẹrin tí a mọ̀ pé ati ní owó bí ìdajì milḷionù kan tí a jẹ sẹ́yìn lórim afẹ́fẹ́ Èyí jẹ́ ǹkan tí ó le gan nítori orúkọ ètò wa lórí tẹlifisọ́nù ni *Yanjú Ọ̀rọ̀ Owó Nà.*

Mo wá ńro wò pé sé a sì le má bá èto yí lọ lórí TV mo nọ wí pé mi ò ni le tẹ̀síwájú pẹ̀lú òtítọ́ tí a kò bá le san owó orí afẹ́fẹ́ Mo ni láti má bá ọ̀pọ̀ ìsiyèméjì jà ní irú àsìkò na. Sùgbọ́n bákanna, Ọlọ́run sì jé olotítọ́, àti pé Drenda nà gbàmí níyànjú gan.

Nínu àlá mi ní ọ̀sẹ̀ na, Ọlọ́run fi hàn mí pé gbogbo àwọn owó nà ni yóò jẹ́ sísan lẹ́kanna, tí mo le sọ pé kòleséese fún èniyàn. Sùgbọ́n ní òpin ọ̀sẹ̀ na ni ilé ìjọsin, gbogbo ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ́ta pọ̀ùn ní ó wolé, owó orí afẹ́fẹ́ ní a san bọ sí déede, bí ó sì ti má ǹbọ sim déédé ní látẹ̀yin wá.

Wow, ìrìn aláràgbàyídá ní láti ilẹ̀ wá!!!!

Ìlànà na wá mú àyípadà wá à wá ǹse ètò *méjì* ní ojúmọ à sì ná milliọnù láti polongo ìhìnrere jáde. Àwá wo èyìn wò a wo gbogbo àwọn tí a dojúkọ nígbana, kò sí wá dàbí nkan tí ó tóbi mọ́ bí ìgbàna. Ó ni láti máa rántí ohun tí akọ nínu orí ìkínní: Ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run nsisẹ́ Pẹ̀lú Rẹ! Rínrín pẹ̀lú Ọlọ́run nínu Ọdún yìí, Mo wa ní òye idí tí ọpọ̀ àwọn ẹ̀pìstélì Páùlù fi bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àwọn Ọ̀rọ̀.

**"Ore-ọ̀fẹ́ àti àláàfíà fún ọ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run Baba wá àti Olúwa wa Jésù Krístì."**

A ní láti rántí pé a kò dá wà. Ore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀, tí ó nró wa lágbára tí ó rékọjá òye, ó nsísẹ́ nínu ayé wa. Ìgboyà ní o le mú wa sọ pé bẹ̀ẹ̀ni kí á sì gbé ìgbésẹ̀ sí ibití a kò tí mọ̀, sùgbọ́n o tọ́ bẹ̀. Mo le sè ẹlẹ́rí èyí.

Èmi ati Drenda ti lọ sí gbogbo ayé láti wàásù ìhìnrere. Àti rí gbogbo àwọn isẹ́ ìyanu tí a kọ sílẹ̀ nínu Májẹ̀mu Titun tí ó ti ṣẹlẹ̀ lójú wa. À ti rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn tí ayé wọn ti yípadà tí wọ́n sì jèrè ilẹ̀ nà. Kò sí ibiti ó dára tó èrèdí!

Àdúrà mí sí ọ ni kí o le má gbé ninu isẹ́ rere gbogbo tí Ọlọ́run ti fi fún ọ láti se, tí ó sì má rántí bí o tí se Pàtàkì tó láti jẹ́ onínurere.

Ní ìpari, ọ̀kan nìyí nínu àwọn Psáàlmù tí mo fẹ́ràn jù:

> *Ẹ fi ìyìn fún Olúwa.Ìbùkún ni fún ọkùnrin náà tí ó bẹ̀rù Ọlọ́run, tí ó ní inú dídùn ńlá sí àwọn òfin rẹ̀. Irú-ọmọ rẹ̀ yóò jẹ́ alágbára ní ayé: ìran àwọn olóòtítọ́ ni a ó bùkún fún. Ọlá àti ọrọ̀ yóò wà nínú ilé rẹ̀; òdodo rẹ̀ sì dúró láé. Fún olóòótọ́ ni ìmọ́lẹ̀ yóò tàn fún ní òkùnkùn: olóore-ọ̀fẹ́ àti aláàánú àti òdodo. Ènìyàn rere fi ojúrere hàn, a sì wínni; ìmòye ni yóò máa fi la ọ̀nà iṣẹ́ rẹ̀. Dájúdájú a kì yóò le yí ní ipò padà láéláé olódodo ni a ó máa ṣe ìrántí rẹ̀ láéláé. Òun kì yóò bẹ̀ẹ̀rè ìyìn búburú ọkàn rẹ̀ ti dúró, ó ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú Olúwa. Ó ti mú ọkàn rẹ̀ gbilẹ̀, ẹ̀rù kí yóò bà á, tìtí yóò fi rí ìfẹ́ ọkàn rẹ̀ lórí àwọn ọ̀tá rẹ̀. Ó ti pín ká, ó ti fi fún àwọn olùpọ́njú; Nítorí òdodo rẹ̀ dúró láé; ìwo rẹ̀ ní a ó gbé sókè pẹ̀lú ọlá Ènìyàn búburú yóò ri,*

*inú wọn yóò sì bàjẹ́, yóò sì pa eyín keke, yó sì yọ dànù: èròngbà ọkàn ènìyàn búburú ni yóò ṣègbé.*

—Orin Dáfídì 112:1-10

Mó fẹ́ràn ibi tí ó ti sọ pe Ènìyàn búburú yóò ri, inú wọn yóò sì bàjẹ́. Ọlọ́run máa ní ọ̀rọ̀ láti sọ gbẹ̀yin. Àṣeyọrí ni ohun ìgbẹ̀san tí ó tóbíjù nígbàgbogbo.

Tí o bá mọ ìtàn mi, wà mọ̀ pé mi  ò se dáda tó kí ntó kúrò ní ilé ìwé Girama pẹ̀lú gíréédì 1.3 Nígbàti Ọlọ́run ní kí nlọ sí kọlẹ́ẹ̀gì lẹ́yìn ìgbàti ó pè mí láti maá wàásù, kì íse nkan tí mo fẹ́.

Nị ọdún`akọ́kọ́ mí nínu kílásì èdè òyìnbó, Mo ní láti kọ̀wé kan. Olùkọ́ mi gbé iwé nà padà fumn mi pẹ̀lú àmì "F" ńlá ní ojú ìwé nà tí wọn sì kọ sí ibẹ̀ pé ǹjẹ́ mo ti lẹ̀ lọ sí ilé iwé Girama rárá. Mo wá ní láti wá olùkọ́ tí yóò ràn mí lọ́wọ́ láti jẹ kí mọ ohun tí mi ò ní ní ilé iwé Girama.

**KỌ́ BÍ ÌJỌBA TI SE NṢIṢẸ́, WÀ SÌ GBÁDÙN AYÉ TÓ DÁRA TÍ ỌLỌ́RUN TI ṢÈLÉRÍ FÚN Ọ.**

Nígbatí iwé mi àkọ́kọ́ jáde, mo gbá imaillí lati ọ̀dọ̀ olùkọ́ àgbà ti èdè–Òyìnbó. Ó ní, "Sé Gary Keesee kanna tí ó wà nínu kílásì mí na nìyí?" Ó yaá lẹ́nu pé mo tí nkọ ìwé.

Hey, Jẹ́kí Ọlọ́run àti ìwọ na ya gbogbo àwọn òrẹ rẹ lẹ́nu!

Ènìyàn tí a jọ lọ sí ilé iwè Girama dúró ní ọjokan ní ibi ilé isé etò ti ìsúná mí ó sì wí pé, "kò ti lẹ̀ ye mi. Gary tí ó feelì jáde kúrò ní ilé iwé Girama, ni ó wa lórí TV tí gbogbo ayé wò?"

Mo nífẹ sí irú àwọn itàn bá wọ̀nyí! Torinà ránti, ìtàn rẹ kò tí tán. Gbìyanjú láti jẹ ẹnití ó lawó bí ó ti ń sojú ọkàn Ọlọ́run ní ibigbogbo tí o bá lọ. Kọ́ bí Ìjọba ti se nsísẹ, wa sì ma gbádùn ayẹ tó dára tí Ọlọ́run ti sèlérì!

—Gary Keesee

*Nítorí iṣẹ́ ìránṣẹ́ ìsìn yìí kò kún ìwọ̀n àìní àwọn ènìyàn mímọ́ nìkan, ṣùgbọ́n ó túbọ̀ pọ̀ sí i nípa ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọpẹ́ sí Ọlọ́run. Nítorí ìdúró yin lábẹ́ ìdánwò iṣẹ́ ìsìn yìí, wọn yóò yin Ọlọ́run lógo fún ìgbọ́ràn yín ní gbígba ìhìnrere Kristi àti nípa ìlawọ́ ìdáwó yín fún wọn àti fún gbogbo ènìyàn. <u>Àti nínú àdúrà fún</u>*

*un yín, ọkàn wọn ń ṣe àfẹ́rí yín nítorí ọ̀pọ̀ oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ti ń bẹ nínú yín. Ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run nítorí aláìlèfẹnusọ ẹ̀bùn rẹ̀!*
—2 Kọ́ríntì 9:12-15

Tí o bá fẹ́ kọ́ ẹ̀kọ́ síwájú sí nípa Forward Financial Group tàbí o fẹ́ fi owó pamọ́ sí investment strategies, sàbẹ̀wò sí forwardfinanncialgroup.com tàbí kí o pè wá sí orí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ yìí 1-(888)-397-3328.

Tí o bá sì fẹ́ se ìwádí síwájú sí nípa Financial Revolution Conferences, tàbí tí o bá fẹ́ gbàlejò fún ìpàdé àpérò, jọ̀wọ́ kànsí wa ní (740)964-7400 kí o sì bèèrè fún ọfísì wa.

Lọ sí **FLNfree.com**
láti gba àgbàsílẹ̀ àwọn ìdánilẹ́kọ́
yìí lọ́fẹ̀ẹ́ ní èdè abínibí rẹ!

Tí o bá fẹ́ ìdánilẹ́kọ́ sí i LỌ́FẸ̀Ẹ́ ní èdè abínibí rẹ
lọ sí **FLNfree.com**

## Ọlọ́run fẹ́ kí o jẹ́ alábùkúnfún kí o sì serere kí o ba le jẹ́ onínúrere ní gbogbo ibikíbi

O kò le di òmìnira láìmláì àyàfi ìgbà tí o bá tó di òmìnira lórí ọ̀rọ̀ owó. Gẹ́gẹ́ bí Èmi àti Drenda ti ń sọ láti bí ọgbọ̀n ọdún sẹ́yìn, o kò le sàwárí ẹnìtí o jẹ́ gan àti màa rìn nínú èrèdí tẹ̀mí fún ayé rẹ títí di ìgbà tí o bá tó yanjú ọ̀rọ̀ ti owó nsọ.

**O LE GBA ÒMÌNIRA!**

Mọ ti fihàn, bẹ̀sì náà ni ẹgbẹgbẹ̀rún àwọn ẹlòmíràn bamkanna. Ore-Ọ̀fẹ́ Ọlọ́run wà nibẹ̀ láti ràn ọ́ lọ́wọ́. Àwọn nkankan wà tí a pè ọ́ sí láti se tí o kò sì ní le seyọrí láìsí owó. O ní láti ní òmìnira lórí owó kí ìse fún ti ara rẹ nìkan àti fún ìdílé rẹ, bíkòse pé bákanna, kí àwọn ènìyàn le rí Ìjọba ti Ọlọ́run tí ó nsisẹ ninú ayé rẹ

**Àwọn ènìyàn ńwá ìdáhùn. Wọ́n ńwá ohun tí ó jẹ́ tọ̀ọ́tọ́ gan. Wọ́n nílò láti rí Ìjọba ní kíákíá tí kí se ẹ̀sìn.**

Ọlọ́run dára, ó sì jẹ́ onínúrere! Nígbatí a bá jẹ́ onínúrere, à ńpìn ọkàn Ọlọ́run fún àwọn ènìyàn. Bí igbàtí a bá dá fẹ́rẹ́ omi tútù mu nínú òòrùn tó mú gangan, tí o bá jẹ́ onínúrere o mú ìtura àti ìrèti wá sínú ayé tí ó wà nínú àginjù àìní.

Nínú ìwé yi tí ńse ẹlẹ́kaàrún irú rẹ̀ tí ó sì jẹ́ èyí tó gbẹ̀yìn nínú àwọn ìwé Yíyí Ètò Ìsúná Rẹ padà tó tẹ̀lé ara wọn láti ipasẹ̀ Gary Keesee, sọ bí o ti se le jẹ́ alábàsisẹpọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run nínú àwọn ise Re àti ìrírí aláràgbàyídá ní ìpele titun ti àseyọrí.

Ní òye tóyè kooro ní ti ìlànà òfin ti Ìjọba ti ó ní agbára ti inúrere àti bí o ti ńsisẹ́ nínú àwọn ìwé tó lápẹẹrẹ tí ó kún fún àwọn ìfihàn titun, àwọn àpẹẹrẹ tó lágbára láti inú Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, àti àwọn ìtàn tómóríyá nipa Gary àti àwọn ẹlòmíràn tí ó lo agbára ti inurere nínu áyé wọn tí wọn ní ìrírí ìyípadà tí ó le bí ẹ̀sì àbájáde.

**Inumrere fi ọkàn rẹ hàn àwọn ènìyàn àti ọkàn Ọlọ́run fún wọn.**



Gary Keese jẹ́ òǹkọ̀wé, sọ̀rọ̀ sọ̀rọ̀, olóko-òwò, onímọ̀ nínú ètò ìṣúná, àti olùṣọ-àgùntàn ẹni tí ó ní ìtara fún rírán àwọn ènìyàn lọ́wọ́ láti borí ní ìgbé ayé wọn, paapaa julo nipa ti igbagbo, idile ati eto isuna. Gari ati iyawo re, Drenda, ti ṣẹ̀dá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn oko òwò, àwọn sì jùmọ̀ jẹ́ olùdásílẹ̀ ti Ìgbé-ayé Ìgbàgbọ́ Ní Báyìí, èyí tí ó jẹ́ àbájáde ètò tẹlifíṣọ̀n méjì—*Yíyanjú Ètò Tó Jẹmọ́ Owó* àti *Drenda*, àpérò kárí-ayé, àti ìpèsè akọ́nimọ̀ọ̀ṣe. Àwọn tọkọ taya Keesee tún jẹ́ oluṣọ́-àgùntàn Ìjọ Faith Life nítòsí Columbus, Ohio.


P. O. Box 779, New ALBANY, OH 43054, USA
garykeesee.com